# AWỌN OJÚ ODÙ MEREERINDINLOGUN

'Wande Abimbọla

*Oxford University Press*
OXFORD LONDON GLASGOW NEW YORK
TORONTO MELBOURNE WELLINGTON CAPE TOWN
IBADAN NAIROBI DAR ES SALAAM LUSAKA ADDIS ABABA
KUALA LUMPUR SINGAPORE JAKARTA HONG KONG TOKYO
DELHI BOMBAY CALCUTTA MADRAS KARACHI

© *Oxford University Press, 1977*

ISBN 0 19 [illegible] 4

AWOKUNLE · D · OLADOKE
MEMBER — : A·O·F·N
ÌLEDÌ - EWEGBEMI
OROMEJI, IBADAN
OYO - STATE

*Printed in Great Britain at the University Press, Oxford by Vivian Ridler, Printer to the University*

*Published by Oxford University Press Nigeria, Oxford House, Iddo Gate, P.M.B. 5095, Ibadan, Nigeria*

# ỌRỌ ÀKỌSỌ

## 1. Ìtàn Ọ̀rúnmìlà

Ifá jẹ́ kókó kan nínú àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ t'ó ti ọ̀run rọ̀ sí Ifẹ̀ Oòdáyé. Ìtàn àwọn òrìṣà fi yé ni pé rírọ̀ ni àwọn òrìṣà wọ̀nyí rọ̀ sílẹ̀ láti ọ̀run. Nígbà tí wọn dé'lé ayé, wọ́n sì ì pé ení l'ó kàn gbogbo rẹ̀ hámíhámú, ni wọ́n bá da òọ̀pẹ̀ tí wọn mú wá láti òde ọ̀run silẹ̀, wọ́n sì tú adìẹ kan ẹlẹ́sẹ̀ márùn-ún tí wọn mú lọ́wọ́ sílẹ̀. Adìẹ náà l'ó tan òọ̀pẹ̀ káàkiri ní Ifẹ̀ Oòdáyé tí gbẹ̀rẹ́fu ilẹ̀ fi hàn jàde l'órí omi kí gbogbo ayé ó tóó wáá di tìgbàtijọ́ tí ó wà báyìí. Ìtàn ṣe fún ni pé Ọbàtálá ni Olódùmarè kọ́kọ́ fún ní iṣẹ́ ìtẹ̀ dá ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe júwe yìí, ṣùgbọ́n nígbà tí Ọbàtálá mọmu yó tán, ó ká lọ̀ dà ilẹ̀ mọ́ ni Odùduà mọ̀wọ̀nrọ̀ bá gba iṣẹ́ náà ṣe. Ìdí níyí tí àwọn ọmọ Odùduà fi di ọba ìlúlú káàkiri ilẹ̀ Yorùbá.

Nígbà tí àwọn òòṣà wọ̀nyí dé Ifẹ̀ Oòdáyé tán, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í dó sí ibi tí ó wù wọ́n. Òkè Ìgẹ̀tì ni Ọ̀rúnmìlà kọ́kọ́ dó sí kí ó tóó wáá lọ sí òkè Ìtasẹ̀. Ìdí níyí tí a fi ń kì Ọ̀rúnmìlà ní:

Ọ̀kùnrin kúkúrú Òkè Ìgẹ̀tì!

Lẹ́hìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún tí Ọ̀rúnmìlà ti ń gbé Ifẹ̀ Oòdáyé, ó fi ibẹ̀ sílẹ̀ lọ sí Adó nibi tí ó ti pẹ́ jùlọ ní òde ìsálàyé. Èyí ló fà á tí a fi máa ń ṣe wí pé:

Adó n'ilé Ifá.

Ṣùgbọ́n kí í ṣe Ifẹ̀ Oòdáyé àti Òtà Ifẹ̀ nìkan ni Ọ̀rúnmìlà gbé nígbà tí ó fi wà láyé. Ó gbé ní Òtà Ifẹ̀ níbi tí ó gbé bí àwọn ọmọ rẹ̀ mẹ́jọ àkọ́kọ́: Alárá, Ajerò, Ọwárángún-àga, Ọlọ́yẹ́mọyin, Òràngún-ọ̀lẹ̀lẹ̀, Elẹ́jẹ̀lú-mẹ̀pẹ̀ àti Ọlọ́wọ̀. Ọ̀rúnmìlà tún gbé ní òde Ọ̀yán níbi tí ó gbé bí ọmọ kan tí ó jẹ́ Amúkankide-Ọ̀yán. Ó gbé ní òde Owó níbi tí ó bí Amọ́sùnkókógi sí.

Ṣùgbọ́n ni Òtà Ifẹ̀ ni Ọ̀rúnmìlà ti padà lọ sí òde ọ̀run tí kò fi tún padà wá sílé ayé mọ́. Ohun tí ó fa pípadà Ọ̀rúnmìlà sí òde ọ̀run ni ìwà àrífin kan tí Ọlọ́wọ̀, àbíkẹ́yìn ọmọ rẹ̀ ní Òtà Ifẹ̀, hù sí i. Ní ọjọ́ kan tí Ọ̀rúnmìlà ń ṣe ọdún ní Òtà Ifẹ̀, ó ranṣẹ́ sí àwọn ọmọ rẹ̀ mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ pé kí wọn ó wáá bá òun ṣe ọdún. Nígbà tí

àwọn ọmọ náà dé, wọ́n ń forí kanlẹ̀, wọ́n sì ń dìde ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, wọ́n sì ṣọ wí pé 'àbọrúbọyè bọ ṣiṣẹ'. Ṣùgbọ́n nígbà tí Ọlọ́wọ̀ dé, ó dúró. Ọ̀rúnmìlà ní ìwọ náà wí pé 'àbọrúbọyè bọ ṣiṣẹ'. Ọlọ́wọ̀ ní òun ò le wí pé 'àbọrúbọyè bọ ṣiṣẹ'. Ọ̀rúnmìlà ní 'è é ti jẹ́'. Ọlọ́wọ̀ náà dá a lóhùn pé:

Ìwọ Ọ̀rúnmìlà sọ̀dún, o sọdún kọ̀;
Òun Ọlọ́wọ̀ náà sọ̀dún, òun sọ̀dún kọ̀,
Ìwọ Ọ̀rúnmìlà f'òsùn ìdẹ lọ́wọ́;
Òun Ọlọ́wọ̀ náà f'òsùn ìdẹ lọ́wọ́.
Ìwọ Ọ̀rúnmìlà bọ sálúbàtà idẹ;
Òun Ọlọ́wọ̀ náà bọ sálúbàtà ìdẹ,
Ìwọ Ọ̀rúnmìlà dádé,
Òun Ọlọ́wọ̀ náà dádé.
Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì ní
Ẹnìkan kì í forí adé balẹ̀ fẹ́nìkan . . .[2]

Ọ̀rọ̀ tí Ọlọ́wọ̀ sọ yìí bí Ọ̀rúnmìlà nínú. Ni Ọ̀rúnmìlà bá gba òsùn ìdẹ lọ́wọ́ Ọlọ́wọ̀, Ó bá kọrí sí ìdí ọ̀pẹ ìgùnkà, èyí t'ó yà sí ya bùkà mẹ́rìndínlógún. Ọ̀pẹ tí a ń wí yìí wà ní ìsálẹ̀ ọ̀run.

Kíkúrò tí Ọ̀rúnmìlà kúrò láyé ba nǹkan jẹ́ gan-an nítorí pé ọgbọ́n Ọ̀rúnmìlà ni àwọn ènìà yókù ń lò láti tún ilé ayé ṣe. Jíjáde Ọ̀rúnmìlà kúrò láyé dàbí fìtìlà wí pé ọgbọ́n ti lọ láyé ní àkókò náà. Ìlọ Ọ̀rúnmìlà ti kúrò láyé tán ni ayé bá dorí kodò. Gbogbo nǹkan dàrú, ó sì dà bí ẹni wí pé ayé fẹ́ parẹ́.

Abóyún ò bí mọ́,
Àgàn ò t'ọwọ́ àlà bosùn.
Ọ̀kùnrin ò dìde,
Akèrèmọ̀dò mẹ́wà ìràwé, . . .[3]

Nígbà tí gbogbo ayé ò mọ ohun tí wọ́n lè ṣe mọ́, ni wọ́n bá kó sí àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún pé kí wọ́n ó lọ bá àwọn baba wọn. Nígbà tí wọ́n dé ìdí ọ̀pẹ ìgùnkà níbi tí Ọ̀rúnmìlà dó sí, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ bàbá wọn, wọ́n ń kì í, wọ́n ń sà á. Wọ́n ń wí pé:

Ifá kó relé o;
Ọmọ Enire,
Ọmọ Enire,
Ọmọ ẹnìkan sàkà bí ìgbọ̀n
Ifá ká relé o,
Ewí ilé Adó,



Ọ̀rà ò 'Defa,
Ẹ̀rìnmí l'ode Ọ̀wọ̀,
Ifá ká relé o;
Mápó Elérè,
Màbà Ọ̀tùn,
Mápó Eléjèlú,
Gbọ̀lájòkòó, ọmọ ọ̀kìnkìn
Tí í mérìn fọn, . . .[4]

Ọ̀rúnmìlà náà dá wọn lóhùn wí pé òun ò tún padà wálé ayé mọ́. Ó ní kí wọn ó tẹ́wọ́, ó wáá fún wọn ní ikin mẹ́rìndínlógún. Ó ní:

B'ẹ́ ẹ bá délé,
B'ẹ́ ẹ bá f'ówó ni,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
B'ẹ́ ẹ bá délé,
B'ẹ́ ẹ bá f'áyá ní,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
B'ẹ́ ẹ bá délé,
B'ẹ́ ẹ bá f'ọmọọ́ bí,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
Ilé t'ẹ bá fẹ́ẹ́ kọ́ láyé,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
Aṣọ t'ẹ bá fẹ́ẹ́ ní láyé,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
Ire gbogbo t'ẹ́ ẹ bá fẹ́ẹ́ ní láyé,
Ẹni t'ẹ́ ẹ́ mọọ bi nù-un.
Ìgbà tí wọ́n délé,
Gbogbo ire náà ni wọ́n ń ní,
Ọ̀rúnmìlà afèdèfẹ̀yọ̀,
Elàsòdè,
Ifá re'lé Olókun kò dé mọ́.
Ó l'ẹni t'ẹ́ ẹ bá ri,
E ní mọọ pé ní baba.[5]

Báyìí ni Ifá ṣe padà lọ sí ìsálẹ̀-ọ̀run, tí kò sì tún fi padà wá sílé ayé mọ́. Ó wáá fi àwọn ikin mẹ́rìndínlógún rọ́pò ara rẹ̀ láyé. Láti ìgbà yìí ikin ti di nǹkan èèlò pàtàkì tí a fi ń bèèrè nǹkan lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà. Lóòótọ́ a kò lè fojú kan Ọ̀rúnmìlà mọ́, ṣùgbọ́n nígbà tí a bá ń fi ikin tàbí ọ̀pẹ̀lẹ̀ dá Ifá, a gbà gbọ́ pé a ń bá Ọ̀rúnmìlà gan-an sọ̀rọ̀, bíba Kèrèfìnùṣọgbọ́n náà ń sì fún wa ní èsì tí ó yẹ.

Ọ̀pìtàn pàtàkì ni Ọ̀rúnmìlà, nígbà tí ó fi wà láyé àti títí di òní-olónìí. Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé Ọ̀rúnmìlà nìkan l'ó mọ àṣírí bí Olódùmarè ṣe dá ayé àti ọ̀run. Òun náà l'ó sì wà níbẹ̀ nígbà tí ẹnikọ̀ọ̀kan fi ń yan ìpín tirẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà ní 'ẹlẹ́rìí ìpín' àti 'ọ̀pìtàn ilẹ̀ Ifẹ̀'.

Àwọn Yorùbá tún gbà gbọ́ pé ọkùnrin kúkúrú ni Ọ̀rúnmìlà, ẹ̀èyàn dúdú sì ni pẹ̀lú. Nítorí náà ni a fi ń ki Ọ̀rúnmìlà ní: 'Ọkùnrin kúkúrú dúdú ọ̀kẹ̀ Ìgẹ́tí.' Ìtàn àwọn òrìṣà tún fi yé ni pé kò sí egungun lára Ọ̀rúnmìlà. Nítorí náà ni Ọ̀rúnmìlà kò fi ní agbára láti ṣe kòró tó bẹ́ẹ̀. Bí ó bá fẹ́ ṣe nǹkan tó nípa àṣẹ Èṣù l'ó máa ń tì bọnu. Ọ̀pọ̀ ni ẹsẹ Ifá tí ó tọ́ka sí èyí.

Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí àwọn Ẹlẹyẹ ń bọ̀ láti ọ̀run wá sí ilé ayé, wọ́n bá Ọ̀rúnmìlà àti àwọn òrìṣà mìíràn ní bodè, wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ̀ wọ́n pé kí àwọn òrìṣà náà ó pọn àwọn dé'lé ayé. Ọ̀rúnmìlà dá wọn lóhùn wí pé:

> Ṣé ẹ rí i pé
> Kò sí egun lára òun.
> Bí òun bá pọn yín,
> Òun ó ní í le rìn mọ́ . . .

ṣùgbọ́n nígbà tí wọn bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ Ọ̀rúnmìlà,

> Ọ̀rúnmìlà bá ti àṣẹ Èṣù bọnu.
> Ifáà tí ó yà ẹnu báyìí,
> Ni àwọn ìyàmí bá ń rọ́ọ̀ sí i
> Ló bá fi bẹ́ẹ̀ gbé wọn délé ayé.*

## 2. Àwọn ohun èèlò Ifá-dídá

(i) *Ikin*. Orísìírísìí ni àwọn ohun èlò Ifá-dídá tí ó wà. Àwọn tí ó ṣe pàtàkì júlọ nínú wọn ni ikin, ọ̀pẹ̀lẹ̀, ìbò, ìrọ̀kẹ̀, ọpọ́n Ifá, Agere Ifá, àpò Ifá, ìlù Ifá, orísìírísìí, ọpa Ọ̀rẹ̀rẹ̀. Ikin l'ó ṣe pàtàkì júlọ nínú àwọn nǹkan wọ̀nyí nítorí pé òun gan-an ni Ọ̀rúnmìlà fi rọ́pò ara rẹ̀ lẹ́hìn ìgbà tí ó ti padà lọ sí òde-ọ̀run tí kò sì wá sílé ayé mọ́. Nínú agere Ifá tàbí àwo Ifá ni a máa ń kó ikin sí, níbẹ̀ ni a sì ti máa ń bọ ọ́ gẹ́gẹ́ bí òòṣà. Ní ọ̀rọ̀ọ̀rún ni àwọn babaláwo máa ń bọ Ifá. Ní àárọ̀ kùtùkùtù ni àwọn ìyàwó Ifá ó ti bẹ̀rẹ̀ sí í pa'lé Ifá. Nígbà tí babaláwo náà bá jí lórí ẹní tán, yóò lọ wúre ní ìdí Ifá, yóò sì fi ikin rẹ̀ dáfá bí ó bá wù ú. Nígbà tí ilẹ̀ bá ta, àwọn babaláwo àti ọmọ Ìkọ́ṣẹ́ Ifá ó bẹ̀rẹ̀ sí í dé, àwọn ìyàwó Ifá ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í wá nǹkan jíjẹ àti mímu fún wọn lẹ́yìn tí wọ́n bá ti bọ Ifá tán. Orísìírísìí



jẹ àti ìmu ni a fi ń bọ Ifá. Ẹsẹ Ifá díẹ̀ tọ́ka sí àwọn nǹkan wọ̀nyí. Fún àpẹẹrẹ, nínú Ọ̀bàrà Méjì, wọ́n sọ pé Ifá fẹ́ràn

> Ọtí abọ́dà,
> Ata tí ó sìjú,
> Obì tí ó làdọ̀
> Ewúrẹ́ méjì a bàmú ṣẹdẹrẹdẹ.?

Nígbà tí àwọn babaláwo bá pa ẹja bọ ikin tán, tí wọn yánlẹ̀ tán, tí wọn jẹ, tí wọn sì mu pẹ̀lú, wọn ó bẹ̀rẹ̀ sí í kífá tí wọn ó sì mu lálà sí i. Ìgbàgbọ́ àwọn babaláwo ni pé kò ní í sí ewu fún àwọn àti ìdílé àwọn mọ́ láàrin ọ̀sẹ̀ náà lẹ́yìn tí wọn ti bọ Ifá. Nípa Ifá bíbọ báyìí ní ọ̀rọ̀ọ̀rún àwọn babaláwo sì le sọ àsọtẹ́lẹ̀ nípa ọjọ́ iwájú kí wọn ó sì fi ẹbọ àti ètùtù lé àwọn ajogun lọ. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé:

> Bí òní ti rí,
> Ọ̀la kì í rí bẹ́ẹ̀
> Ni babaláwo fi ń dífá ọ̀rọ̀ọ̀rún.

(ii) *Ọ̀pẹ̀lẹ̀*. Nǹkan kejì pàtàkì tí a fi ń dá Ifá ni ọ̀pẹ̀lẹ̀. Ọmọ ni ọ̀pẹ̀lẹ̀ jẹ́ fún ikin ṣùgbọ́n ó wúlò púpọ̀ nítorí pé ó rọrùn láti fi dá Ifá. Ọmọ mẹ́jọ ni ọ̀pẹ̀lẹ̀ ní: mẹ́rin ní apá ọ̀tún àti mẹ́rin ní apá òsì. Ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn ọmọ wọ̀nyí ni ó ní inú àti ẹ̀yìn. Bí a bá dá ọ̀pẹ̀lẹ̀ mọ́lẹ̀, ọmọ kọ̀ọ̀kan lè kọ inú síta tàbí kí ó kọ ẹ̀yìn. Èyí sì ni a fi ń dá Odù tí ó bá yọ mọ̀ bí a bá ti dá Ifá tán.

Orísìírísìí ọ̀pẹ̀lẹ̀ ló wà. Àdáyébá ibẹ̀ ni èyí tí a fi awẹ́awẹ́ èso igi ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣe. Ṣùgbọ́n a lè fi idẹ tàbí irin ṣe ọ̀pẹ̀lẹ̀. Ọ̀pẹ̀lẹ̀ onídẹ jẹ́ ọ̀pẹ̀lẹ̀ Ọ̀ṣun. Irú iṣẹ́ kan náà ni gbogbo àwọn ọ̀pẹ̀lẹ̀ yí ń ṣe, bákan náà ni a sì ṣe ń lò wọ́n fún Ifá dídá.

(iii) *Ìbò*. Bí a bá ti dá Ifá kalẹ̀ tán, tí a sì ti mọ Odù tí ó jáde, à máa lo ìbò láti wá ìdí Odù yí délẹ̀ kodoro. A lè fẹ́ mọ ẹni gan-an tí Odù yí jáde sí, bí ẹni tí ó wáá dáfá gan-an ni o tàbí ẹ̀èyàn rẹ̀ kan. A tún máa ń lo ìbò láti yan ẹbọ àti láti bèère lọ́wọ́ Ifá ibi tí a ó gbé ẹbọ náà sí. Orísìírísìí ìbò l'ó wà. Pàtàkì júlọ nínú ni *egungun* àti *owó ẹyọ*. Egungun dúró fún 'bẹ́ẹ̀ kọ́', owó ẹyọ sì dúró fún 'bẹ́ẹ̀ ni'. Àwọn nǹkan mìíràn tí a tún ń lò láti lé ìbò nìwọ̀nyí: *èhìjẹ́ àwo* dúró fún ayé tí ó ṣe ó àwo tí ó fi fọ́; *kòró ìyìn* dúró fún Ọ̀rúnmìlà alára, baba dúdú rẹrẹ ọ̀kẹ̀ Ìgẹ́tí.

(iv) *Ìrọ̀kẹ̀*. Ìrọ̀kẹ̀ jẹ́ ohun èlò Ifá dídá tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà bí a bá tí ń dá Ifáà lọ. A tún máa ń pè é ní ìrọ́fá. Eyín erin ni a fi ń gbẹ́

ìrọ̀kẹ̀ ṣùgbọ́n a lè fi ìdẹ tàbí igi lìndìn gbẹ́ ẹ. Ìsàlẹ̀ ìrọ̀kẹ̀ tí a ń mú lọ́wọ́ tóbi ṣùgbọ́n òkè rẹ̀ níbi orí rẹ̀ ri ṣóńṣó. Ohun gan-an ni à bá tún máa pè ní '*òkò ṣe ribiti ṣori ṣóńṣó*'. Orísìírísìí nǹkan ni wọ́n yà sí ara ìrọ̀kẹ̀ bíi obìnrin tí ó kúnlẹ̀ tí ó si gbé ọpọ́n lọ́wọ́ àti àwọn ẹ̀yàn tí ń jó, tí wọ́n si ń yọ̀. Ibi ṣóńṣó orí ìrọ̀kẹ̀ ni àwọn babaláwo máa ń fi ṣọ́ inú ọpọ́n Ifá bí wọ́n bá ti ń dá Ifá lọ.

(*vi*) *Ọpọ́n Ifá*. Orísìírísìí ọpọ́n Ifá l'ó wà. Òmíràn rí roboto, òmíràn ní igun mẹ́rin, òmíràn sì dà bí oṣù tí ó ti kọrùn lójú ọ̀run. Bí àwọn babaláwo bá fi ìkin dá Ifá, dandan ni kí wọ́n ó ní ọpọ́n Ifá nínú èyí tí wọ́n ó máa tẹ̀ ẹ́ sí. Ìyẹ̀rosùn ni a máa ń kó sínú ọpọ́n yìí, nínú iyẹ̀ yìí ni a sì máa ń tẹ Ifá sí.

Orísìírísìí ọnà ni àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà ṣe yí etí ọpọ́n Ifá ká. Ní àárín ọpọ́n náà ni a ya ojú mẹ́jì tí ó mọ́lẹ̀ kedere sí. Àwọn ẹlòmíràn sọ pé ojú Èṣù ni èyí. Ojú náà dà bí ẹni pé ó wo babaláwo tí ń dáfá. A lè rí orísìírísìí àwòrán mìíràn bí àwòrán ahun, ejò àti adìẹ tí ó yí ojú gbàńkù gbàńkù mẹ́jì yí ká.

(*vi*) *Agere Ifá tàbí Àwo Ifá*. Nínú awo yìí ni àwọn babaláwo máa ń kó Ifá sí. Wọ́n a máa fi igi gbẹ́ agere Ifá pẹ̀lú ìdérí rẹ̀. Nítorí pé ibẹ̀ ni a ń kó ìkin tí ó dúró fún Ọ̀rúnmìlà sí, àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà ní láti fara balẹ̀ gbẹ́ ẹ kí wọ́n ó sì ṣe ọnà tí ó jojúnígbèsè sí i lára. Ẹsẹ Ifá kan tí ó sọ̀rọ̀ nípa agere Ifá sọ wí pé nígbà ni gbogbo irú ọmọ ẹ̀dá ń gbé tí Ọ̀rúnmìlà gégé bí ẹlẹ́rìí-ìpín sì ti ń yọ tí onikálùkù fún un. Ó ní:

> Orí tí ó dáàdé,
> Nínú agereade ni í ti í yọ̀ọ̀ wá.
> Ọ̀rùn tí ó le ògìgbààlèkè,
> Nínú agereade ni í ti í yọ̀ọ̀ wá.
> Bòbèèdí tí ó le mọ́ninji,
> Aṣọ ọba t'ó kòmá yanran yanran,
> Nínú agereade, ni í ti í yọ̀ọ̀ wá.[8]

(*vii*) *Àpò Ifá*. Ọnà pàtàkì kan tí a fi lè dá babaláwo mọ̀ ni nípa àpò tí wọ́n máa ń kọ́ sí èjìká. Èyí l'ó sì fà á tí a fi ń pè wọ́n ní akápò. Nínú àpò yìí ni wọ́n máa ń kó gbogbo ohun èèlò Ifá dídá sí. Babaláwo kì í rìn kò sí àpò Ifá. Bí a bá pàdé babaláwo lójú-ọ̀nà, tí a bá sọ pé kí ó dá Ifá fún ni, tọ́ọ̀ ni ó yọ ọ̀pẹ̀lẹ̀ rẹ̀ jáde nínú àpò tí ó gbé kọ́ èjìká, ìgè yá nù-un. Aṣọ ni a fi ṣe àpò yí ṣùgbọ́n à máa fi kìkìdà ìlẹ̀kẹ̀ olówó iyebíye ṣe àpò Ifá mìíràn.

Àpò Ifá mìíràn tí ó tún wà ni èyí tí à ń pè ní *àpò jèrùgbé* nítorí



pé nínú rẹ̀ ni àwọn babaláwo ń kó gbogbo èrù tí wọ́n bá jẹ sí. Ṣé bí ọpọ́n bá tẹ̀jú nígbà mìíràn, babaláwo le jẹ́rìí:

> Òtítí baba ajé;
> Ọ̀fọ̀gìnìngìnì, awọ 'Balà àti
> Àkóńkotán ohun ọrọ̀ mìí.

(*viii*) *Ìrè Ifá*. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ní ìbẹ̀rẹ̀, àwọn babaláwo a máa ṣe àríyá ní ọ̀rọ̀ọ̀rún tàbí ìgbàkúgbà tí wọ́n bá pé jọ láti dá Ifá tàbí láti ṣe ètùtù. Kíi ṣe tí òpèlọpó ẹsẹ Ifá ti ń sọ pèlú:

> Agogo ni Ìpòrò,
> Àran níkòjà,
> Ọ̀pá kugúkugu l'ójúlé Ìgèrèmaghe.
> Wọ́n sọpé sàràn,
> Ò mú tìnùn rẹ̀ jáde.
> Wọ́n yí Àgbà sí mọ́ran àkà.
> Ó ya fún kòtò,
> Orìn awo ni ó kọ.
> Ẹsẹ̀ tí ó nà,
> Ìjó fà á,
> Ọwọ́ ìjó, ọrẹ̀ ayọ̀.

Àwọn tí ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú ìlù Ifá ni àràn tàbí *Ìpèsè*. Àwọn babaláwo a sì tún máa lu àgbá tí í ṣe ìlù àwọn Ọ̀gbóni. Àwọn ìlù mẹ́jèèjì yí ni à ki ní:

> Àgbá bori pọ̀rọ̀,
> Ìpèsè abeghàrí jìnbìjìnbìkunjin.

Agogo tún jẹ́ pàtàkì kan nínú ìlù Ifá. Ọ̀pá ni wọ́n ń fi ń lù ú. Ohun ni àwọn babaláwo fẹ́ràn láti máa fi ṣe àríyá kàkàkiri ní àárín ìlú.

(*ix*) *Ọ̀pá Ọ̀rẹ̀rẹ̀ tàbí Ọ̀pá*. Èyí jẹ́ ọ̀pá kan tí a fi irin tàbí idẹ ṣe tí àwọn babaláwo olóyè máa ń tẹ̀ kàkiri. Ọ̀nà gan ni ọ̀pá yìí jẹ́ sí fún àwọn babaláwo, kò sí ohun tí ẹgbẹ́ kanlẹ̀ rárá. Lára ìgirí ni kọ́ọ̀ ilẹ̀ ni àwọn babaláwo máa ń fi ọ̀pá yìí tì sí. Èyí l'ó fà á tí a fi máa ń wí pé: '*Ọ̀pọ̀ gangangan l'ọ̀ à bóọ́n*.' Bíbọ ni àwọn babaláwo máa ń bọ ọ̀pá yí nítorí pé ọ̀pá àṣẹ ni. Ọ̀pá yìí ni Ọ̀rúnmìlà gbà lọ́wọ́ Olówó ọmọ rẹ̀ ní Ọ̀tà Ilẹ̀ kí ó tó di wí pé Ọ̀rúnmìlà lọ dó sí ìdí ọ̀pẹ àgùnká, tí kò fi padà wá sílẹ̀ ayé mọ́. Níbi ọ̀pá yìí máa ni àwọn babaláwo tí mú orúkọ bí Amòsùn, Awórọ̀ àti Ọ̀rúnmìlà tí wọ́n ń sọ ọmọ wọ́n.

## 3. Àwọn Ojú Odù

Bí ó bá ṣe wí pé ọ̀pẹ̀lẹ̀ ni a fi dá Ifá, a ó kó gbogbo ikin mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún sí ọwọ́ kan, a ó si gbìyànjú láti fi ọwọ́ kejì kó gbogbo rẹ̀ kúrò nínú ọwọ́ àkọ́kọ́. Bí ikin tí ó kù ní ọwọ́ kìíní bá jẹ́ méjì, a ó ṣe àmì kan síni iyẹ̀rosùn tí a ti bù sínú ọpọ́n Ifá tí ó wà níwájú babaláwo. Bí ó bá ku ikin kan ṣoṣo péré, a ó ṣe àmì méjì. A ó ṣe àmì báyìí ní ẹ̀ẹ̀mẹrin sí apá ọ̀tún àti ẹ̀ẹ̀mẹrin míràn sí apá òsì. Àpapọ̀ àmì mẹ́rin apá ọ̀tún àti mẹ́rin apá òsì wọ̀nyí ni à ń pè ní Odù.

Bí ó bá ṣe Ojú Odù l'ó jáde, gbogbo àmì apá ọ̀tún ni láti rí bákan náà pẹ̀lú ti apá òsì. Èyí l'ó fà á tí 'Èjì' fi máa ń bẹ̀rẹ̀ orúkọ Ojú Odù tàbí kí 'Méjì' ó parí orúkọ wọn. Àwọn Ojú Odù jẹ́ mẹ́rìndínlógún (16), àwọn ọmọ Odù (nígbà tí àwọn àmì òpó apá ọ̀tún bá yàtọ̀ sí ti òsì ni a ń pe Odù tí ó jáde ní Ọmọ-Odù tàbí Àmúlù-Odù) si jẹ́ igba-ó-lé-ogójì (240). Orúkọ àwọn Ojú Odù mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún nìwọ̀nyí:

1 Èjì Ogbè  2 Ọ̀yẹ̀kú Méjì  3 Ìwòrì Méjì
4 Òdí Méjì  5 Ìrosùn Méjì  6 Ọ̀wọ́nrín Méjì
7 Ọ̀bàrà Méjì  8 Ọ̀kànràn Méjì  9 Ògúndá Méjì
10 Ọ̀sá Méjì  11 Ìká Méjì  12 Òtúúrúpọ̀n Méjì
13 Òtúá Méjì  14 Ìrẹtẹ̀ Méjì  15 Ọ̀ṣẹ́ Méjì
16 Òfún Méjì.

Àwọn àmì tí ó dúró fún Odù kọ̀ọ̀kan nìwọ̀nyí:

| (1) | (2) | (3) | (4) |
|---|---|---|---|
| I I | II II | II II | I I |
| I I | II II | I I | II II |
| I I | II II | I I | II II |
| I I | II II | II II | I I |
| Èjì Ogbè | Ọ̀yẹ̀kú Méjì | Ìwòrì Méjì | Òdí Méjì |

| (5) | (6) | (7) | (8) |
|---|---|---|---|
| I I | II II | I I | II II |
| I I | II II | II II | II II |
| II II | I I | II II | II II |
| II II | I I | II II | I I |
| Ìrosùn Méjì | Ọ̀wọ́nrín Méjì | Ọ̀bàrà Méjì | Ọ̀kànràn Méjì |

| (9) | (10) | (11) | (12) |
|---|---|---|---|
| I I | II II | II II | II II |
| I I | II II | I I | I I |
| I I | I I | II II | I I |
| II II | II II | II II | I I |
| Ògúndá Méjì | Ọ̀sá Méjì | Ìká Méjì | Òtúúrúpọ̀n Méjì |



| (13) | (14) | (15) | (16) |
|---|---|---|---|
| I I | I I | I I | II II |
| II II | I I | II II | I I |
| I I | II II | I I | II II |
| I I | I I | II II | I I |
| Òtúá Méjì | Ìrẹtẹ̀ Méjì | Ọ̀ṣẹ́ Méjì | Òfún Méjì |

Bí ó bá ṣe Ọ̀pẹ̀lẹ̀ ni a lò, a ó gbé e nalẹ̀ níwájú ẹni, a ó si wo ìye awẹ́ ọ̀pẹ̀lẹ̀ tí ó ṣíjú sókè tàbí tí ó bọ ìyìn sókè lára apá ọ̀tún àti ọwọ́ òsì ọ̀pẹ̀lẹ̀ náà. Àpapọ̀ iye awẹ́ tí ó ṣíjú sókè tàbí tí ó bọ ìyìn sókè ní apá ọ̀tún àti òsì ni ó dúró fún àmì Odù kọ̀ọ̀kan. Fún àpẹẹrẹ, bí gbogbo awẹ́ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin apá ọ̀tún bá ṣíjú sókè tí gbogbo awẹ́ mẹ́rin ti apá òsì náà sì ṣíjú sókè, àmì Èjì Ogbè ni èyí. Ṣùgbọ́n bí awẹ́ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin apá ọ̀tún àti tòsì bá dojú dẹlẹ̀, àmì Ọ̀yẹ̀kú Méjì ni èyí dúró fún.

Àwọn Ojú Odù mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún l'ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú gbogbo igbàlélẹ́gbẹ̀ta-ó-dín-mẹ́rin (256) Odù tí ó bọ̀ lẹ́yìn. Àwọn gan-an si ni baba fún àwọn Ọmọ Odù. Ṣùgbọ́n àwọn Ojú Odù náà si tún ní àgbà àti ọmọdé. Èjì Ogbè ni àgbà fún gbogbo wọn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àtàn sọ fún wa pé Òfún Méjì ni baba fún wọn tẹ́lẹ̀ rí nígbà tí wọn fi ń bọ̀ láti òde ọ̀run. Ṣùgbọ́n lónìí, Èjì Ogbè ni àgbà Odù; Ọ̀yẹ̀kú Méjì àti Ìwòrì Méjì l'ó si tẹ̀lé e gẹ́gẹ́ bí a ṣe to wọn sí òkè yí.

## 4. Ipò Ifá láàrin àwọn òrìṣà yòókù

Àgbà òrìṣà ni Ifá jẹ́. Ìtàn àwọn òrìṣà fi yé wa wí pé nígbà tí àwọn òrìṣà dó si Ifẹ̀ tán, Ògún l'ó ṣán ọ̀nà lọ fún ibi tí wọn kọ́ dé sí títí tí wọn fi dé ibi tí wọn fẹ́ẹ̀ dó sí nítorí pé òun ló ni àdá lọ́wọ́ tí wọn fi la ọ̀nà dé ibẹ̀. Ẹsẹ Ifá kan tọ́ka si èyí nígbà tí ó wí pé:

> Ọ̀rúnmìlà l'ó dáràá dé 'Fẹ̀,
> Mo l'ó dáràá dé 'Fẹ̀,
> Bẹ́ẹ̀, Àgbọnmìrègún.
> Wọ́n ní ta l'ó kọ́ d'Otù Ifẹ̀ nígbàà?
> Wọ́n ní Ògún ni.[2]

Nítorí náà a lè sọ pé Ògún ni àgbà àwọn òrìṣà nítorí pé òun l'ó kọ́ dé'lẹ̀ ayé.

Àwọn míràn tí sọ pé Ọ̀ọ̀sàálá ni olú àwọn òrìṣà nítorí pé nílńkíbí ni wọ́n tí ó bọ ọ́. Ṣùgbọ́n ohun kò sọ òrìṣà kan di olú fún èkejì nítorí pé kí i ṣe Ọ̀ọ̀sàálá nìkan ni wọ́n ń bọ nibi gbogbo.

Òrìṣà míràn tí ó tún jẹ́ àgbà ni Èṣù. Òun ni alásẹ fún gbogbo

àwọn òrìṣà yòókù. Òun l'ó máa ń fi ọ̀dà àṣẹ tí Olódùmarè fi dá ayé àti ọ̀run pamọ́ fún àwọn òrìṣà yòókù. Bí àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù bá fẹ́ lo àṣẹ yìí, wọ́n ní láti tọrọ àṣẹ lọ́wọ́ Èṣù ni, wọ́n ó sì dá a padà bí wọ́n bá ti lò ó tán.

Fún àpẹẹrẹ, Ọ̀rúnmìlà pàápàá kò dá agbára kankan ní nítorí pé kò sí ẹgungun lára rẹ̀. Àṣẹ Èṣù l'ó máa ń lò nígbà gbogbo tí ó bá fẹ́ ṣe nǹkan tí ó lágbára. Bíbẹ́ẹ̀bẹ́ a kò lè ka Èṣù sí Ọbàrìṣà.

Gẹ́gẹ́ bí ohun tí a rí nínú Ifá, Ọ̀rúnmìlà ni à ń pè ní Ọbàrìṣà. Ọ̀rúnmìlà ní Òkànrán Méjì tọ́ka sí nígbà tí ó ní pé:

Ikú wàá pin nígbà yí ò,
Ikú pin.
Ikú pin,
Ikú pin,
Lágbọ̀dẹ̀ àṣẹ́ún.
Adìẹ ìpìpà,
Ikú àwó mọ̀ mọ̀ wàá pin lọ́wọ́ Ọbarìṣà.[19]

Ìdí tí Ọ̀rúnmìlà fi jẹ́ Ọbàrìṣà ni wí pé òun l'ó wà lọ́dọ̀ Olódùmarè nígbà tí Olódùmarè fi ń dá ayé àti ọ̀run. Ìdí nìyí tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà ní 'Ẹlẹ́rìí-ìpín, Ọgbọ́n ilé ayé, Òpìtàn àti Ifẹ̀'. Nítorí náà Ọ̀rúnmìlà le pìtàn ayé àti ọ̀run, ó sì le pa ìtàn àwọn òrìṣà yòókù pìtàn. Èyí l'ó sọ Ọ̀rúnmìlà di ọba láàrin àwọn ìbọ.

Ìdí mìíràn tí a fi lè sọ pé Ọ̀rúnmìlà ni Ọba àwọn òrìṣà ni pé Òun ni ẹnu fún gbogbo àwọn òrìṣà yòókù. Bí òrìṣà kan bá ń bínú sí ni tàbí ó fẹ́ ṣe nǹkan kan fún àwọn t'ó ń sìn ín, l'ẹ́nu Ọ̀rúnmìlà l'a ó ti gbọ́ nígbà tí a bá lọ sí oko aláwo. Gbogbo àwọn òrìṣà ńláńlá pàtàpàtà l'ó ní Odù tí wọ́n nínú Ifá. Fún àpẹẹrẹ, Òkànràn Méjì jẹ́ Odù Ṣàngó, Ògúndá Méjì sì jẹ́ Odù Ògún. Nínú àwọn Odù Méjì yìí ni a ti lè rí nǹkan nípa ìtàn Ṣàngó àti Ògún. Nínú àwọn Odù tí ó jẹ mọ́ òrìṣà kọ̀ọ̀kan ni ti ń fọhùn sí àwọn tí ń sìn wọ́n.

Ọ̀nà mìíràn tí a tún fi lè sọ pé Ifá ni Ọbàrìṣà ni pé òun l'ó ni ètùtù àti ẹbọ ní ìkáwọ́. Lẹ́yìn ìgbà tí àwọn òrìṣà bá ti fọhùn nínú Odù t'ó jẹ mọ́ wọn tán, a ní láti ṣe ẹbọ èyí tí ó jẹ́ oúnjẹ fún àwọn òrìṣà náà. Nítorí náà, a lè sọ pé Ọ̀rúnmìlà l'ó ń pàṣẹ sí àwọn òrìṣà yòókù lẹ́nu.

Nítorí àwọn ọ̀nà pàtàkì tí a ti là sílẹ̀ wọ̀nyí, Ifá ni Ọba fún àwọn òrìṣà. Bí Ifá kò bá sí láyé mọ́, yóò ṣòro kí àwọn òrìṣà yòókù ó wà láyé. Bí Ifá kò bá sí parun láyé, àwọn òrìṣà yòókù kò lè parun. Ṣùgbọ́n bí orin Ifá kan:



Irọ́ ni wọ́n pa,
Ifá ò leè parun.
Ekè ni wọ́n ṣe,
Ifá ò leè parun.
Àtẹ̀lẹwọ́ l'a bálá,
Àwa ò m'ẹni ó kọ ọ́.
Irọ́ ni wọ́n pa,
Ifá ò leè parun.

**5. Àwọn nǹkan pàtàkì pàtàkì tí Ifá máa ń sọ̀rọ̀ dá lé lórí**

Nítorí pé Ifá jẹ́ àkójọpọ̀ ọgbọ́n, ìmọ̀ àti ìrírí àwọn Yorùbá, kò níí ya ni lẹ́nu pé orísìíríṣìí nǹkan nípa ìrò ọkàn àti ìṣe àwọn Yorùbá ló pé sí inú rẹ̀. Nítòótọ́, a ò mẹ́nu ba díẹ̀ nínú àwọn nǹkan wọ̀nyí, a ó sì tọ́ka sí àwọn ẹsẹ Ifá tí wọ́n ti jẹ jáde.

(i) *Ọ̀rọ̀ nípa orí, ìyè àti àyà.* Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé yíyàn ni a máa ń yan orí láti òde ọ̀run wá. Orìṣàńlá ló ń dá ènìyàn, tí ó ń dá ojú, imú àti ẹnu, ṣùgbọ́n Olódùmarè ló ń fún ènìyàn ní ẹ̀mí. Àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà ni a sọ pé Ògún ló ń rọ egungun ènìyàn. Èyí tí ó dá ni lójú ni pé ọ̀dọ̀ Àjàlá ni a ti ń yan Orí-inú. Orí-inú yìí ló dúró fún àyànmọ́ tàbí ìpín àwa ọ̀dá. Ẹni tí ó bá yan orí-rere lọ́dọ̀ Àjàlá ní láti ṣorí rere láyé pàápàá jùlọ bí ohùnwọn bá fi ọwọ́ àti ẹsẹ̀ ara rẹ̀ ṣiṣẹ́ kún orire tí ó yàn lọ́run.

Odù Ọ̀gbègúndá l'ó pìtàn bí ènìyàn ṣe ń yan orí lọ́run. Ọwọ́ ara ìmúkàkàkà ni í fi í gbé orí t'ó bá wù ú. Ṣùgbọ́n nítorí pé ọ̀mùtí àti onígbèsè ni Àjàlá, olómọ tí í mọrí, púpọ̀ nínú àwọn orí tí ó mọ sílẹ̀ ni kò dára t'ó sì jẹ́ orí burúkú. Òmíràn tòbi lásán, ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ wí pé Àjàlá kò mọ jinà. Òmíràn sì ti fọ́ sára. Nítorí náà ni àwọn orí tí Àjàlá mọ dúdúlà tí ó sì tún mọ jinà wà. Ẹni tí ó bá fi ọwọ́ ara rẹ̀ gbé èyí tí ó fọ́ sára tàbí tí wọ́n ó mọ jinà yẹ kò mọ̀ dájú pé kí òun ó tóó rìn dé òde ayé, orí burúkú náà ó ti yínrìn dànù tàn lọ́nà nígbà tí òjò bá dé. Ṣùgbọ́n òjò àti òòrùn kò ran orí tí Àjàlá bá ti mọ jinà wá lát'òde ọ̀run.

Ẹni tí ó bá yan orí rere n'ilé Àjàlá, b'ó bá dé'lé ayé tan, ó di bí ó máa ri ṣe, kí ó máa kọ́lé mọ́lé, kí ó máa l'ágbàlá kánrin. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ l'ó ń jẹ́ 'Òlùtí baba ajé; Ọlọ́gìnìngìnì ọmọ 'Bàdà àti Akọ́nkọ́tin olum ọmọ nIfẹ̀.'

Ẹni tí ó bá yanri burúkú n'ilé Àjàlá, b'ó ṣiṣẹ́ ṣiṣẹ́ kò leè rere kankan jẹ. Ìrírí kan náà t'ó wà fún irú ènìyàn bẹ́ẹ̀ ni kí ó máa

rúbọ kíkan kíkan. Ẹbọ eirú yìí ni ó máa bá a kún orí burúkú t'ó gbé ua títí tí yóò fi tún padà sọ di dé dédéé èyí tí gbé kúrò l'ódò ọ̀run. Nígbà náà ni ẹni tí ó ní orí náà ó tóó máa rí ṣe. Ọ̀rúnmìlà nìkan náà l'ó lè f'ẹbọ ṣe eléyìí nítorí pé òun ni 'Odùdù tí í dúró emèrè. T'ó tún orí ẹni aumwọ̀n ṣe.'

Ṣùgbọ́n a nílàti rántí pé àti ẹni tí ó yanrí rere o, àti ẹni tí ó yanrí burúkú, gbogbo wọn l'ó nílàti fi ọwọ́ àti ẹsẹ̀ ṣiṣẹ́ kí wọn ó tóó dunire. Nítorí náà orí rere ṣíyàn l'ọ́dọ̀ Àjàlá le ṣài sọ èèyàn dunire bí olúwarẹ̀ kò bá ṣiṣẹ́. Orí rere tí olúwarẹ̀ yàn ó wá nìbẹ̀ lásán ni, kò ní í so èso rere.

Olum tí ó le mú orí rere so èso náà ni ẹsẹ̀. Ẹni tí ó yan orí rere ṣùgbọ́n tí kò mú ẹsẹ̀ agangun ń tan araa rẹ̀ jẹ lásán ni nítorí pé ìre kò níí tẹ̀ ẹ́ lọ́wọ́. Ese Ifá kan ṣe àlàyé èyí nígbà tí ó sọ pé:

> Ọ̀pọ̀bọ̀ mọ̀ mọ̀ dé ó,
> Àwo ẹsẹ̀.
> Ẹnìkan kì í gbìmọ̀ràn
> K'ó yọ ẹsẹ̀ lẹ̀.[11]

Kò sí ẹni tí ó lè sọ irú orí tí òun yàn lọ́run, bí owe ni o tàbí burúkú àfi Ọ̀rúnmìlà nìkan, ṣùgbọ́n bí èèyàn bá fi ọwọ́ àti ẹsẹ̀ ṣiṣẹ́ tí ó sì ń rúbọ ní ìgbọràn sí àwọn babaláwo, bó pẹ́ títí olúwarẹ̀ ó dunire.

Nǹkan mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì ní àyà, èyí tí a fi ń yan ọ̀rẹ́. Èèyàn níló ọ̀rẹ́ tí ó mọ bá olúwarẹ̀ gbìmọ̀ràn nípa ìgbésí ayé olúwarẹ̀. Ọ̀rẹ́ yìí náà ni ó máa bá olúwarẹ̀ pète pèrò nípa ọjọ́ iwájú. Èyí ni àwọn baban wá fi wí pé: 'Ọ̀rẹ́ ẹni ni í bá ni í pilẹ̀ ọrọ̀. Ará ilé ẹni ní í bánil ní an.' Olum tí ó dúró fún ọ̀rẹ́ nínú bure ara èniyàn ni àyà. Bí èèyàn yan orí rere jù bẹ́ẹ̀ lọ, bí kò bá fi àyà yan ọ̀rẹ́ rere, ìmọ̀ràn olúwarẹ̀ kò ní í gún ní gẹ́gẹ́.

Ese Ifá oríṣìríṣìí ṣe àlàyé nípa ọ̀rẹ́. Ifá sọ wí pé ọ̀rẹ́ ju baba àti ìyá ẹni lọ. Ọ̀rẹ́ ju ọmọ-ìyá àti ìbátan gbogbo lọ. Òòṣà papàá tẹ̀ ní ọ̀rẹ́. Nítorí náà ni a kò fi gbọdọ̀ dalẹ̀ ọ̀rẹ́. Ó ní:

> Igbó yìí, wọn ó jugbó a gbé bí ni.
> Ọ̀dàn yí, wọn ó jọ ọ̀dàn ibi ní mo wà.
> Bí a bá bùrìn bùrìn,
> T'á a b'ọ̀rẹ́ pàdé,
> Wọn a yá j'ẹni a bí ni bí lọ.
> A dìfá f'ọ̀rẹ́ ẹni,
> A bù f'úlúkù ẹni.
> Ìyá ẹni ẹ̀ é f'ifáá hun ni.
> Baba ẹni ẹ̀ é f'ifáá hun ni.
> Ọ̀rẹ́ nìkan l'ó f'ifá hàn mí.
> Olum tí mo bá rí,
> Ng ó máa b'ọ̀rẹ́ ẹ̀ mi jẹ,
> Olúkù dìdùnjú . . .
> Ó ní Òòṣà lọrẹ́ o,
> Ẹ mú dalẹ̀ o,
> Òòṣà lọrẹ́ o,
> Ẹ mú dalẹ̀ o,
> Ẹni t'ó bá mọ̀rẹ̀,
> K'ó ẹ mọ̀ dalẹ̀.
> Òòṣà lọrẹ́,
> E mú dalẹ̀.[12]

[iv] *Ìwà.* Bí àwọn Yorùbá ṣe gba orí gbọ́, bẹ́ẹ̀ náà ni wọn si gba ìwà gbọ́. Orí jẹ́ olum tí èniyàn ń mú wá láti ọ̀run, ṣùgbọ́n onikálùkù l'ó máa ń yan ìwà tirẹ̀ láyé. Orísìí méjì ni ìwà tí ó wà láyé—ìwà rere àti ìwà búburú. Èyí tí ó bá wu onikálùkù l'ó le yàn nínú. Ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá wí pé ìwà búburú ni òun ó máa hù, kí ó mọ̀ dájú pé òun le rí ìjà àwọn òrìṣà àti àwọn ará ọ̀run pẹ̀lú nítorí pé àwọn irúnmọlẹ̀ kà ìwà èèyàn bẹ́ẹ̀ sí ọ̀dàlẹ̀.

Olum tí àwọn Yorùbá gbà gbọ́ ni wí pé bí èniyàn tilẹ̀ yan orí rere, tí ó sì lọwọ́ àtẹsẹ̀ ṣiṣẹ́ láyé, bí kò bá ní ìwà rere, ayé àti ọ̀run rẹ̀ kò lè dára. Olódùmarè àti àwọn òrìṣà ń fẹ́ kí àwọn ẹdá ó máa hu ìwà rere sí ọmọnìkejì wa. Ẹni tí ó bá ń hu ìwà búburú bí olè-jíjà, ìlẹ̀-dídà àti ìkà-ṣíṣe, àwọn òrìṣà l'ó máa ń fi ìyà jẹ irú èèyàn bẹ́ẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, Ṣàngó l'ó máa ń pa olè àti èké. Èèyàn àti Ìlẹ̀ l'ó sì máa ń yẹjú àwọn ọ̀dàlẹ̀.

Ìwà tí à ń wí yìí, Ifá sọ fún wa pé obìnrin ni àti wí pé aya Ọ̀rúnmìlà ni. Nígbà tí Ìwà ọ̀binrin tí ó ń bá kò lẹ́gbẹ́ mọ́, ni Ọ̀rúnmìlà bá kọ Ìwà, aya rẹ̀, sílẹ̀. Ní Ìwà bá bínú lọ sí àtì Olódùmarè. Ṣe ọmọ Olódùmarè sì ni Ìwà nítorí pé òun ni í ṣe àkọ́bí Sùúrù èyí tí í ṣe àrẹ̀mọ Olódùmarè. Nítorí èyí ni a fi máa ń sọ pé 'Sùúrù ni baba ìwà.' Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà kọ Ìwà sílẹ̀ tán ni ayéé rẹ̀ kò bá dára mọ́. Kò rí ṣe mọ́, kò rí jẹ, kò rí mu, bẹ́ẹ̀ ni gbogbo èèyàn kò sì rí i lọ. Nígbà tí ayé Ọ̀rúnmìlà wáá dorikodò nítorí pé Ìwà ná-dẹ, kò bá múra láti wá obìnrin rẹ̀ lọ. Ṣe wọn ní:

> Bí Ìwà bá nu èèyàn,
> Ẹyin ò mọ̀ wí pé ayée rẹ̀ kò ná dẹ.

Ọ̀rúnmìlà bọ́ sínú ẹ̀kù Eégún, ó bẹ̀rẹ̀ sí í wá obìnrin rẹ̀ kààkiri. Ó wá a dé'lé Alárá, Ẹ̀jì Ọ̀sà, ọmọ amúrín kàn dọ̀gbọ̀n ogogo. Ó wá a dé'lé Ajerò, ọmọ ọ̀gbọ̀jọ̀ kọ̀rọ̀ ìjà jọ̀ọ̀. Ó wá a dé'lé Ọwáràngún àga, ìmọ̀tà òdè, onígòrò, àgùn l'ọwọ́ làbà owó tèrèrè. Ó wá dé gbogbo ilé àwọn ọbàjà mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún, ṣùgbọ́n kò rí i. L'ó bá gbọ̀nà òde ọ̀run lọ. Níbẹ̀ l'ó ri wá rí Ìwà. Ó bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ̀ ẹ́ pé kí ó bá òun kálọ̀ sí ilé, ṣùgbọ́n Ìwà ni òun kò lọ. Ó wáá kí Ọ̀rúnmìlà ní ìlọ̀ pé kí ó máa fi ọwọ́ ara rẹ̀ tún ìwà ara rẹ̀ ṣe láyé. Láti ọjọ́ náà l'ó ti di wí pé ọwọ́ ọnikálùkù l'ó nílati fi tún ìwà ara rẹ̀ ṣe.

Ìtàn yí fi yé ni wí pé ẹ̀gbin àti ìwọ̀si ń bẹ nibi kí á máa hu ìwà rere, ṣùgbọ́n a nílati fi ara mọ́ ọn kí ayé wa ó lè bàà dára. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ń tọ́jú obìnrin ẹni ni a ní láti máa tọ́jú ìwà ara ẹni. A kò gbọdọ̀ jẹ́ kí ó ṣí lọ nílé ẹni. Ohunkóhun tí èèyàn bá ní tí wọn bá sọ pé kò ní ìwà, ohun náà di ẹ̀gbẹ́ àti òtòhànrẹ̀. Ó ní:

> Ìf'á a lọwọ́,
> Ìf'á à níwà,
> Owó olówó ni.
> Ìwà, ìwà l'à ń wá o,
> Ìwà.
> Ọmọ l'a bí, t'á à níwà,
> Ọmọ ọlọ́mọ ni.
> Ìwà, ìwà l'à ń wá o,
> Ìwà.

Díẹ̀ nínú àwọn ìwà rere tí àwọn òrìṣà àti ará ọ̀run ń fẹ́ kí á máa hù ni kí á máa sọ òtítọ́, kí á sì máa ní sùúrù. Ó ní:

> Ibínú kò da nnkan kan fún ni.
> Sùúrù baba ìwà.
> Àgbà t'ó ní sùúrù,
> Ohun gbogbo l'ó kó já.
> A dífá fún Ọ̀rúnmìlà.
> Ifá ń sunkún lọ Ìwó Àte. . . .
> Ìyà t'Ifá jẹ ní wíwà,
> L'ó bíkọ, l'ó bàbo.[15]

Nípa kí á máa sọ òtítọ́, Ọ̀rúnmìlà wí báyìí pé:

> Ó lè gbe ni jùkà o,
> Mo l'ó lè gbe ni jùkà.
> Òtítọ́, mo l'ó lè gbe ni jùkà.



Díẹ̀ nínú àwọn ìwà búburú tí àwọn òrìṣà àti àwọn ará ọ̀run ò fẹ́ ni ìlọ̀-dìdà, èkẹ́, ìdódó, àti olè-jíjà. Ó ní:

> Òdódó ní í pẹrú,
> Ẹ̀pè, wọn a sì polè.
> Ìlọ̀dìlà ní í pọ̀rẹ̀
> Alájọbí ni í pàjọkan t'ó ṣobi.
> A jọ gb'órí ìlẹ̀, a jobu.
> A jọ gb'órí ìlẹ̀, a jẹjà.
> A jọ gb'órí ìlẹ̀, a jẹ kókó ìgbín.
> Àṣẹ d'ọwọ́ ilẹ̀, a jọ nu.[16]

(iii) *Ìtàn àwọn òrìṣà.* Gbogbo òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá l'ó ní Odù tirẹ̀ nínú Ifá nibi tí a ti lè rí ìtàn òrìṣà kọ̀ọ̀kan. Fún àpẹẹrẹ, ìtàn Ifá ń bẹ nínú Ẹ̀jì Ogbè, tí Ṣàngó ń bẹ nínú Ọ̀kànràn Mẹ́jì. Bákan náà ni Ọ̀sá Mẹ́jì ṣe jẹ́ Odù àwọn Ìyàmi, nítorí náà ni a ṣe ń pè é ní Ọ̀sá Ẹlẹ́yẹ. Òtúá Mẹ́jì l'ó pa ìtàn ẹ̀sìn Mùsùlùmí, bẹ́ẹ̀ sì ni Òtúúrúpọ̀n Mẹ́jì pa ìtàn Eégún.

Nínú ìtàn àwọn òrìṣà wọ̀nyí ni a ti lè mọ̀ nípa ìgbésí-ayé àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá kọ̀ọ̀kan, ohun tí òrìṣà kọ̀ọ̀kan fẹ́ràn láti máa jẹ tí a sì le fi rúbọ fún un, àti ibi tí a lè kà sí ilé àwọn òrìṣà náà.

Nínú ẹsẹ Ifá tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yí, a rí i kà wí pé Ṣàngó, ẹni tí à ń pè ní Àrìrà, ni ọmọ Ọ̀ràànyàn ní ìlú ayé àtijọ́ kan tí à ń pè ní Òkò. Ẹsẹ Ifá náà tún sọ fún wa pé ní àkókò tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yí Ṣàngó ń bẹ láàrin ìgbìrì ọ̀tá; ṣùgbọ́n lẹ́yìn ìgbà tí ó fi ọta rúbọ, l'ó ba di pé ó ń fi ọta (èyí ni ẹdùn àrá) ṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀. Ó ní:

> Pàtìmbọ̀là okirìbìtì.
> A dìá fún Àrìrà gàgàgà,
> Èyí tí í ṣ'ọmọ Ọ̀ràànyàn l'Òkò.
> Nígbà tí Ṣàngó ń bẹ láàrin ìgbìrì,
> Tí Olúlànà ń bẹ láàrin ọ̀tá.
> Ńjẹ́ kín l'Àrìrà fi ṣẹ́tẹ́?
> Igba ọta.
> Igba ọta l'Àrìrà fi ṣẹ́tẹ́.
> Igba ọta.[17]

Nínú ẹsẹ Ifá tí ó wà nísàlẹ̀ yí, èyí tí a mú láti inú Òtúúrúpọ̀n Mẹ́jì, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn Eégún. Ó sọ pé ọmọdé àti ọ̀gbẹ̀ri kò lè mawo Eégún, àfi bí a bá fawo hàn wọ́n. Ó tún sọ̀rọ̀ nípa àwọn ibi mẹ́jì kan—igbó Gẹ̀ẹ̀gẹ̀ẹ̀se àti ọ̀dàn Gbágbalò—nibi ti Eégún gbé ń jó wẹ̀kẹ̀wẹ̀kẹ̀ pẹ̀lú aṣọ rẹ̀. Ẹsẹ Ifá náà lọ báyìí:

Igbó nígbóo Gẹ̀gẹ́ẹ̀re.
Ọ̀dàn ni ọ̀dàn Gbógbofó,
Ọ̀dàn Gbógbofó l'ẹ́gún gbé ẹ̀wọ́ ajọ wẹ̀lẹwẹ̀lẹ.
A díá fún onítafà
Tí ó tolo lá wàlè.
Wọ́n ní kí onítafà ó rúbọ.
Ó sì rú u.
Ìgbà t'ó rúbọ tán,
Ó sì là.
Ó ní bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́
Ni àwọn awo ìmọ̀ ń ṣẹnu rereé pefá,
Ọmọdé yìí ó mawo,
Jẹ́ ng l'awo hàn ọ́.
Ẹgbẹ̀rí ó mawo,
Jẹ́ ng fawo hàn ọ́.[16]

Ẹsẹ Ifá tí ó wà nísàlẹ̀ yìí sọ̀rọ̀ nípa Aláàpíni, ìpẹ̀kun ayé Ẹ̀rgún. Ó sì tún sọ̀rọ̀ nípa atọ, ohunun tí a bí pẹ̀lú ìṣẹ̀n Ẹ̀rgún kíwọ̀ ọ́, tí a sì gbà pé ó mú àṣẹ wá láti ọ̀run láti mawo Ẹ̀rgún. Ó ní;

Olúùgbẹ̀gbẹ̀ l'ó díá fún Aàtàgbiní,
Mọ̀ọ́dọ̀únigbè, atu kòkoó ebẹnu jẹ́gẹjẹ̀gẹ,
A díá fún Aláàpìní, Ọ̀fọ̀rìjẹ̀dàsókùn,
Nígbà tí ó ń sọ̀unù gbàràhùn ọmọ.
Rírú ẹbọ ni i gbe ni.
Àìrú kì í gbéèyàn.
Ẹ wáá bá ni ní màrìnrin ọmọ.[17]

Ọ̀sá Méjì ni Odù t'ó pilẹ̀ àwọn àjẹ́. Nítorí náà ni a ṣe ń pe Odù yì ní Ọ̀sá Ẹlẹ́yẹ. Odù yí ṣe àlàyé bí ó ṣe jẹ́ wí pé ọ̀tá ni àwọn àjẹ́ àti àwọn òrìṣà. Olúun tí ó fa ọ̀tá wọn ni pé àwọn òrìṣà wá fún ìránkọ́wọ̀ àwa ẹ̀dá nígbàtí àwọn ẹlẹ́yẹ àti ajogun dúró fún ìparun àwa ẹ̀dá.

Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ta ko araa wọn. Bí àwọn ẹlẹ́yẹ́ ti ń ta ko àwa ẹ̀dá ni wọ́n ń ta ko àwọn òrìṣà náà pẹ̀lú. Nínú ẹsẹ Ifá tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yí àwọn ẹlẹ́yẹ́ fẹ́ pa Ọ̀rúnmìlà, ṣùgbọ́n nígbà tí ó rúbọ, ó sì ní ìṣẹ́gun. Ẹsẹ Ifá náà lọ báyìí:

Òtítẹ̀, omi ẹyẹ,
Gbẹ̀dùdù gbẹndu, omi Òòṣà Òwùjìn.
A díá fún Ọ̀rúnmìlà, Ọ̀rẹ̀rẹ̀mọ́gbó,



Tí ó l'omú tiẹ̀ lé,
Tí ó ṣọn omi Ẹlẹyẹ.
Wọ́n ní kí Ọ̀rúnmìlà ó rúbọ
Kí àwọn Ẹlẹyẹ ó mọ̀ baá pa á.
Ó sì rú u.
Ìgbà t'ó rúbọ tán,
Ní ọpá àwọn Ẹlẹyẹ ò bá lèé kà á mọ́.
Ó ní bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́
Ni àwọn awo ìmọ̀ ń ṣẹnu rereé pe 'Fá,
Òtítẹ̀, omi ẹyẹ,
Gbẹ̀dùdù gbẹndu, omi Òòṣà Òwùjìn,
A díá fún Ọ̀rúnmìlà, Ọ̀rẹ̀rẹ̀mọ́gbó,
Tí ó l'omú tiẹ̀ lé,
Tí ó ṣọn omi Ẹlẹyẹ,
Àdá gbẹ́ẹ́ mi,
Àdá ọ̀gà.[18]

(iv) *Àwọn Ajogun àti àwọn Ẹlẹyẹ*: Ẹsẹ Ifá orísìírísìí l'ó sọ̀rọ̀ nípa àwọn ajogun. Ifá fi yé wá wí pé mẹ́jọ ni àwọn ajogun. Àwọn mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ náà ni Ikú, Àrùn, Òfò, Ẹ̀gbà, Ọràn, Ẹ̀pè, Ẹ̀wọn, Ẹ̀se. Gbogbo àwọn ajogun tí a dárúkọ wọ̀nyí, ọmọ ọ̀dọ̀ Èṣù ni wọ́n jẹ́. Àwọn ajogun kò fẹ́ ire fún àwa ènìyàn bí kò ṣe ibi. Wọn kò fẹ́ ire fún àwọn òrìṣà náà nítorí pé àwọn òrìṣà wà fún ìrànlọ́wọ́ àwa ẹ̀dá.

Èṣù ni ó jẹ́ alákòóso fún àwọn Ajogun, àwa èèyàn àti àwọn ìlọ̀ kí Èṣù kí àwọn ajogun ó dígbò lu ẹni tí ó bá rúbọ. Ìdí nìyí tí a fi ń ṣe pé ẹni tí ó rúbọ ni Èṣù gbè. Ṣùgbọ́n ẹni tí kò rúbọ rí kò ní ṣẹ́gun, nítorí tí ó bá wu àwọn Ajogun l'ó lè ó ohunrere ṣe nítorí pé Èṣù kò ní í gbà oníwarẹ̀. Èyí l'ó fà á tí a fi máa ń wí pé 'ẹni ó rúbọ ni Èṣù gbè'.

Ẹbọ ni a fi ń lé àwọn ajogun kúrò l'ọ̀dọ̀ ẹni. Bí Èṣù bá ti gba ẹbọ yìí, yóò sọ fún Ajogun náà pé kí ó fi oníwarẹ̀ sílẹ̀. Àwọn babaláwo lè tún ka ẹ̀ẹ̀wọ̀ tàbí ewé fún irú èèyàn bẹ́ẹ̀ t'ó fi jẹ́ pé àwọn Ajogun kò fi ní í lè pa á mọ́. Nínú ẹsẹ Ifá tí ó wà nísàlẹ̀ yí, a ó í kà pé ikú àti àrùn wá Òdùdúwà pupa ìkè Àgà lọ sí ilé, ṣùgbọ́n wọn ò lè dá a mọ̀ mọ́ nítorí pé àwọn babaláwo ti fi bùjé pa á lára, ó sì ti di èèyàn dúdú. Ẹsẹ nínú ẹsẹ Ifá náà lọ báyìí:

A díá fún Òdùdúwà pupa ìkè Àgà
Èyí tí ikú tàbùn ó kan 'lé rẹ̀ẹ́ rè,
Ajogun gbogbo ó kan lée rẹ̀ ní ìlọ ní ìlọ.
Ni àwọn ọmọ rẹ̀ẹ́ bá ní kò rú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹbọ.

Ni wọn fi mú Ìára bùjé nàà fi ṣe á fẹ́m.
Ni ó bá di ẹ̀èyàn dúdú fafa.
Ni àwọn ajogun ò bá lè dà a mọ́ mọ́.[19]

Bí a bá ti rúbọ f'ẹsù, dandan ni ki ajogun ó pẹ̀yìndà. Ẹbọ nikan ni a lè fi ṣẹ́gun àwọn Ajogun. Ìdí nìyí tí ìgbà ẹsẹ Ifá fi máa ń parí pẹ̀lú irú ọ̀rọ̀ báwọ̀nyí:

Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Ẹ wáà bá wa ní àrúṣẹ́gun.
Arúṣẹ́gun l'àwá wà.

*Tàbí:*

Rírú ẹbọ ní í gbe ni,
Àìrú kì í gbèèyàn.
Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Ẹ wáà bá ni láìkú kangiri
Àìkú kangiri l'a ń bọ̀.

Ìtàn kan pàtàkì tí ó wà láàrin àwọn Ẹlẹ́yẹ àti àwọn Ajogun ni pé kò sí ìdàmúlójú pé àwọn Ẹlẹ́yẹ́ ó gba ẹbọ tí a bá rú fún wọn. Wọn kò sí ní ohun ọ̀fun àwọn òrìṣà kan lọ rárá. Wọn tilẹ̀ á yọ àwọn òrìṣà náà lẹ́nu nígbà tí ó bá wù wọ́n. Ẹbọ àwọn Ẹlẹ́yẹ ni à ń pè ní èèsè. Ẹmjà èèsè ni ẹpo pupa, ìfun ẹran, ẹ̀dọ̀ ẹran àti ẹ̀jẹ̀ ẹran. A ó kàá gbogbo rẹ̀ sínú agbada. Ní oríta mẹ́ta ni a máa ń sáábà gbé ẹbọ wọn sí. Ṣùgbọ́n nínú ìgbà tí ó jẹ́ wí pé a kò ní ìdàmúlójú bí wọn ó gba ẹbọ náà tàbí wọn ó ní í gbà á, orí ẹni nikan ni a lè máa bẹ̀ sí fún ìgbàlà lọ́wọ́ àwọn àjẹ́. Ẹsẹ Ifá tí ó wà nísàlẹ̀ yí sọ wí pé orí ẹni l'ó lè gba ni lọ́wọ́ àwọn Ẹlẹ́yẹ.

Òkè l'ó ṣẹ̀yin gùnmọ̀ọ̀ :
Ifá ẹni arinmọ̀ẹ̀rìn.
Ifá l'ó bá jà ko rìn,
A dùnú sí.
A difá f'òkọ̀ọ̀kànlélọ́gún irúnmọlẹ̀,
Wọ́n ń tọrun bọ̀ wáyé.
A difá fún Ẹlẹ́yẹ,
Ẹlẹ́yẹ ń tọrun bọ̀ wáyé . . .
A difá fún Ọ̀rúnmìlà,



Ọ̀rúnmìlà ń t'Ìkọ̀lé ọ̀run bọ̀ wá sí tayé
Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Orí mi ni ó gbà mí lọ́wọ́ Ẹlẹ́yẹ.[20]

Odù tí ó pìtàn àwọn Ẹlẹ́yẹ jù nínú Ifá ni à ń pè ní Ọ̀sá Mẹ́jì tàbí Ọ̀sá Ẹlẹ́yẹ. Odù yí ṣe àlàyé orísìírìsìí ìṣàkóso tí ó ṣẹlẹ̀ láàrin àwọn Ẹlẹ́yẹ àti àwọn òrìṣà. Fún àpẹẹrẹ, àwọn Ẹlẹ́yẹ bá 'Tàlàbí, ọmọ Ògún jà nígbà tí ó lọ pọndò Ẹlẹ́yẹ. Wọ́n tún bá Yemọja, obìnrin Ògún náà jà nígbà tí ó lọ pọnmi l'odò àwọn Ẹlẹ́yẹ, tí ó fi bu gbogbo ojú omi jẹ. Wọ́n bá Ògúnkùlà pegàà jà nínú ẹsẹ Ifá tí ó lọ báyìí:

Orórò', omi ẹyẹ,
Gbẹ́ndú gbẹ́ndu, omi Ògún Onírè.
A difá fún Òṣàdà, Ọ̀rẹ̀rẹ̀mọ̀gbò,
Tí ó l'omi tirẹ̀ 'lọ,
Tí ó pọn omi Ẹlẹ́yẹ.

Ọ̀rúnmìlà l'ó ń fi Ògún àti àwọn ọmọ pẹ̀lú ìyàwó rẹ̀ yọ lọ́wọ́ àwọn Ẹlẹ́yẹ ní gbogbo ìgbà tí àwọn Ẹlẹ́yẹ bá ń dà wọ́n láàmú. Nígbà tí 'Tàlàbí ọmọ Ògún tí sá di Ọ̀rúnmìlà l'ó ń gbàgbé àlà tí ó mú lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ Ọ̀rúnmìlà. Àdí náà ó bọ́ lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà títí di òníolónìí. Àdí náà ni à ń pè ní Àdá Ògún.

Obìnrin ni gbogbo àwọn Ẹlẹ́yẹ pátá pàá. Àwọn ni à ń kì báyìí nínú Ifá:

Ìyàmi òsòròngà,
Apanimọ́mọ̀ràgùn, olókìkí òru,
Ajẹ̀dọ̀ tútù mọ́ bí,
Obìnrin kùkùmí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ṣẹ̀,
Ẹyẹ tí í lọ nígbà ọjà bá tú.

Wọn ní ẹyẹ kan tí wọ́n lọ rẹ̀ ń jẹ́ ẹ̀lúnú. Ẹyẹ yìí a máa jáde lóru, a sì máa gbe ẹ̀èyàn tàbí ẹranko tí ó bá ṣẹ àwọn Ẹlẹ́yẹ mì. Àwọn Àjẹ́ fúnra wọn a máa yípadà di ẹyẹ nígbà tí ó wù wọ́n. Ìdí nìyí tí a fi ń pè wọ́n ní Ẹlẹ́yẹ.

(vi) *Ẹbọ*. Ẹbọ-rírú ṣe pàtàkì púpọ̀ láàrin àwa Yorùbá. Lọ́nà kìíní, ẹbọ ni a lè fi ṣẹ́gun àwọn ajogun. Bí a bá ti rúbọ tán, dandan ni ki àwọn Ajogun ó pẹ̀dà lẹ́yìn ẹni tí wọn ń ṣe. Ìdí nìyí tí Ifá fi sọ wí pé:

Onidodo gba dòdò,
Onipupá gba pupa,
Aláyinrin gbàyinrin.
Baraapetu, ó bá mọ mọ kòkò u kárim.
Baraapetu.

Ẹsẹ Ifá kan tí ó tí yé ni pé ìpàkọ̀ ara ẹni ni ẹbọ-rírú jẹ́. Nígbà tí àwọn Ajogun bá dé, tí wọn ní gbógun ti ni, bí a bá fi nǹkan ìní ẹni bí owó, aṣọ, ẹku, ẹja, ẹran, epo tàbí oúnjẹ mìíràn kẹ́bọ rú, tí Èṣù bá sì ti gba ẹbọ náà tí ó gbé e fún àwọn ajogun, dandan ni kí wọn ó pẹ̀yìn dà, kí wọn ó sì lọ. Ẹsẹ Ifá náà lọ báyìí:

Baba gbóbó erin;
Baba kọ̀ọ̀ ẹfọn;
Ọgbọnrangandan nídàbòm ẹmọ-ìdò;
Ifá ni' máfiẹ̀ẹ̀ mi abapá yabúgọ;
Yẹ́rrù kan ṣeṣọ ó le gbàkùmrin mẹ́jì;
Pààrọ̀paarọ, awo ilé Ẹlẹ́pẹ̀.
A dìá fún Ẹlẹ́pẹ̀.
Wọ́n ní ó l'ódìdí ẹran ṣàárọ̀ aran rẹ̀
Nínorí ikú.
Ó gbọ́ rírú ẹbọ,
Ó rú.
Ó gbọ́ ẹ̀rù àrùkàṣu,
Ó tù.
Ó gbọ́ Ìkaràra ẹbọ ba fún un.
Ó wáà ń yín àwọn awo rẹ̀.
Àwọn awo rẹ̀ ń yin 'Fá.
Ó yà ẹnu kótó,
Orin awo l'ó bọ́ sí i lẹ́nu.
Ẹsẹ̀ tí ó nà,
Ijó fà á.
Ó ní bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́
Ni àwọn awo òun ń ṣẹnu rere pe 'Fá. . . .
Ikú wáá f'Ẹlẹ́pẹ̀ẹ́ 'lẹ̀,
Orí ẹran ló mú lọ.
Pààrọ̀ paarọ, awo ilé Ẹlẹ́pẹ̀.
Àrùn wáá f'Ẹlẹ́pẹ̀ẹ́ 'lẹ̀,
Orí ẹran ló mú lọ.
Pààrọ̀ paarọ, awo ilé Ẹlẹ́pẹ̀.
Òfò wáá f'Ẹlẹ́pẹ̀ẹ́ 'lẹ̀.



Orí ẹran ló mú lọ.
Pààrọ̀ paarọ, awo ilé Ẹlẹ́pẹ̀.
Ajogun gbogbo wáá f'Ẹlẹ́pẹ̀ẹ́ 'lẹ̀,
Orí ẹran ló mú lọ.
Pààrọ̀ paarọ, awo ilé Ẹlẹ́pẹ̀.[11]

Èṣù tí ó jẹ́ ọ̀rẹ̀mọ́jà láàrin àwọn ajogun àti àwọn òrìṣà pẹ̀lú ẹ̀mi ẹ̀dá ló máa ń gba ẹbọ tí a bá rú. Ìdí nìyí tí a fi máa ń gbé ìpín ẹbọ sí idi Èṣù. Àìmọ̀ọ̀n ni ti Èṣù nibi gbogbo ẹbọ tí a bá rú. Bí Èṣù bá tí mú mìíràn tirẹ̀ nínú rẹ̀ tán, yóò máa gbé iyókù fún ajogun tàbí òrìṣà tí a rú ẹbọ náà fún. Èyí ló fà á tí a fi máa ń wí pé:

Èṣù nìí gba ẹbọ
Bẹ́ẹ̀ ni kò mọ Ifá dá.

Nítorí ìgbà tí ó jẹ́ wí pé ọmọ ìṣẹ̀ Èṣù ni gbogbo àwọn ajogun, kò ní ṣòro fún Èṣù láti pàṣẹ fún ajogunkájogun tí a rú ẹbọ náà fún láti gba ẹbọ náà kí ó sì fi ẹni tí ó rúbọ náà sílẹ̀. Bí ó bá sì ṣe wí pé Òrìṣà ló ń yọ onítọ̀hún lẹ́nu, kò ní ṣòro fún Èṣù láti gbà ẹbọ náà fún òrìṣà ọ̀hún nítorí wí pé Èṣù ni alágbà fún gbogbo àwọn òrìṣà.

Ìdí kejì pàtàkì tí a fi ń rúbọ ni wí pé ẹbọ jẹ́ oúnjẹ fún àwọn òrìṣà àti òkú ọ̀run gbogbo. Àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ wí pé gbogbo àwọn ìbọ nílò láti máa jẹun nígbà gbogbo. Ìdí nìyí tí a fi ń bọ àwọn òrìṣà ní ọ̀rọ̀ọ̀rún, tí a sì ń yàn ọ̀nà oúnjẹ fún wọn nígbà gbogbo tí a bá ń jẹun. Òrìṣà kọ̀ọ̀kan ló ní oúnjẹ tirẹ̀ tí ó fẹ́ràn jù. Fún àpẹẹrẹ, ọkà àmàlà, gbẹ̀gìrì àti ẹran àgbò ni oúnjẹ fún Ṣàngó; Ẹ̀gún a sì máa gba ọtí pẹ̀lú obì; Ifá a máa gba:

Eku mẹ́jì olúwéré,
Ẹja mẹ́jì abìwẹ̀gbàdà;
Ewúrẹ́ mẹ́jì abàmú rẹ̀derẹ̀dẹ̀;
Ẹiyẹ mẹ́jì tó fìwọ yíyákó;
Ẹyẹ mẹ́jì abìfò ga-ngo.
Ata tí ó ṣìjọ,
Obì tí ó làlà,
Ọtí abọ̀da.

Bí ó ṣe wí pé a ń rúbọ ni o, tàbí a ń ṣe ìṣẹ̀ òrìṣà, ó ṣe pàtàkì kí a fún àwọn ìbọ ní nǹkan tí wọn fẹ́ràn láti jẹ kí wọn ó lè bá yọnú sí ni.

Idí mìíràn pàtàkì tí a fi ń rúbọ ni láti wá òòrìṣà sí araa wa lọ́rùn. Bí ènìyàn bá rúbọ tán, àwọn ará ilé àti alábàágbéè rẹ̀ ni láti jẹ nínú ẹbọ náà, kí ó tóó fi iyókù yànlẹ̀ sí àwọn òrìṣà. Nínú ti a gbé ń ṣẹbọ, tí a ń jẹun ati ìmọ̀ràn ó ti máa wá láti ẹnu àwọn tí a pè jọ nàá tí wọn ó si rìnrin tọ̀ ni ọ̀nà nípa nǹkan tí a torí rẹ̀ rúbọ. Ní ìgbà kí í ṣe gbogbo ẹbọ ni a ń pe èèyàn sí, ṣùgbọ́n ẹbọ tí ó bá tí la à ti ṣeyọn, a ó se òòrìṣà lọ, dandan ni kí a pe ọmọ aráyé sílẹ̀ nítorí pé a gbà gbọ́ pé ẹnu aráyé lẹbọ. Ẹsẹ Ifá kan láti inú Odù Ọ̀wọ́nrín Méjì ó fi yé wa pé ẹnu ọmọ aráyé ni à ń lọ nílẹ̀. Ó ní:

Agbọ̀ngbọ̀n, awo wọn l'ode Ìbíníẹ̀.
Agbààyàngidì, awo ode Ìjẹ̀ṣà.
Ọ̀kánrin yàngidì yangidi
Ni wọ́n dá ní àrìpá.
A dífá fún Olóríyìnmẹ́fún,
Yóó bulẹ̀ Olówu mko,
Wọ́n ní ó bọgùn ilé.
Ó bọgùn ilé,
Ẹbọ rẹ̀ ò fín.
Wọ́n ní ó bóòṣà ojà.
Ó bóòṣà ojà,
Ẹbọ rẹ̀ ò dà.
Òòṣà ojà ò gbà.
Wọ́n ní ó bọrí.
Ó bọrí,
Orí pà.
Wọ́n ní ó bọlẹ̀,
Ó bọlẹ̀,
Ilẹ̀ lu.
Wọ́n ní ó lọ Olúbẹ̀bọ̀tíríbọ̀, baba ẹbọ.
Ó ní ìràn mọ̀ pé baba ẹni l'Ẹ̀gùn ilé.
Òún mọ̀ pé iyá ẹni l'Òòṣà ojà.
Ó ní òún ṣe'orí kíri n;
Òún m'ọlẹ̀ nílẹ̀.
Ó ní òun ò mọ ohun tí í jẹ́ Olúbẹ̀bọ̀tíríbọ̀, baba ẹbọ.
Wọ́n ní ẹnu,
Ẹnu ní í jẹ́ Olúbẹ̀bọ̀tíríbọ̀, baba ẹbọ.
Ẹ̀ẹ̀ àìn l'a ń lọ nílẹ̀.
Ẹnu wọn.
Ẹnu wọn l'a ń lọ nílẹ̀,
Ẹnu wọn.
Mo fún'gbá,
Mo f'àwo.
Ẹnu wọn,
Ẹnu wọn kò mọ̀ lí ri ni bá jà.
Ẹnu wọn,
Mo wálẹ̀,
Mo wàrà.
Ẹnu wọn.
Ẹnu wọn kò mọ̀ lí-ri ni bá jà.
Ẹnu wọn.[12]

Nítorí náà ẹbọ jẹ́ nǹkan tí a fi ń pa ará ayé, òkú ọ̀run, àwọn òrìṣà àti àwọn ajogun lẹ́nu pọ̀ sí ìbikan kí wọn ó le lọ́wọ́ sí nǹkan tí a fẹ́ ṣe. Ẹsẹ tí ó jẹ́ aláàlà kúrìn gbogbo àwọn tí a dárúkọ wọ̀nyí (ọmọ aráyé, òkú ọ̀run tàbí Ẹ̀gùn, àwọn òrìṣà àti àwọn ajogun) kò ní í lọ́wọ́ sí nǹkan tí a fẹ́ ṣe bí kò bá rí ẹbọ tí yóò fi aiwàjú nítorí pé 'ẹni ó rúbọ ni Ẹ̀ṣù gbè'.

Bí a bá tún wò ó ní ọ̀nà mìíràn, ẹbọ jẹ́ ònà pàtàkì fún àwọn babaláwo papàá. Nínú ẹbọ tí a bá rú, Ifá lé fún babaláwo láyè láti mú lò nǹkan fún araa rẹ̀. Irú nǹkan báyìí tí babaláwo máa ń rí mú sílẹ̀ lára ẹbọ ni à ń pè ní ẹ̀rú. Ṣùgbọ́n dandan ni pé kí babaláwo ó fún àwọn ajogun àti àwọn ìbọ ní tí wọn nínú ẹbọ, kí ó tóó mú ẹ̀yí tí Ifá bá fún un láyè láti mú nínú sílẹ̀ fún tí araa rẹ̀. Nígbà ìgbà tí ó jẹ́ ni pé àwọn babaláwo kò ní owó oṣù, ọ̀nà ọ̀nà Ifá báyìí ni wọn fi ń rí owó tí wọn n jẹ.

Ẹbọ sì tún jẹ́ ònà fún àwọn ọ̀tanka bí ajá àti ẹyẹ ojú ọ̀run bí igún. Nítorí pé igún fẹ́ràn ẹbọ-jíjẹ ni a fi máa ń dá orúkọ rẹ̀ mọ́ ẹbọ rúbọ gbogbo. Ẹsẹ Ifá kan ń ṣe àlàyé wí pé bí a kò rí gúnnugún, a kò lèè ṣe ẹbọ, b'ó ń r'ákàlà, a ó ṣe. Ẹsẹ Ifá náà lọ báyìí:

Ṣàlàgẹ̀rẹ̀jẹ̀ l'ó dífá fún gúnnugún,
Ọmọ Olójúgbòòkàrà.
Ṣàlàgẹ̀rẹ̀jẹ̀ wáá jẹbọ . . .
A ṣẹ́ bá ò rí gúnnugún,
A kì yóò lè ṣẹbọ.
B'á ò r'ákàlà,
A ó ṣe.
Ṣàlàgẹ̀rẹ̀jẹ̀ wáá jẹbọ.
Igún wáá jẹbọ,
K'ẹbọ ó lè bá Ọ̀...

Etiẹ́ wàá jẹbọ,
Kẹ̀bọ ó lè baà dà.
Igún, ètiẹ́, ọmọ Lódè.
Sàlìgẹ̀rẹ̀jẹ́ wàá jẹbọ.

(vi) *Ire*. Bí a bá ti rúbọ fún àwọn ajogun àti àwọn àwọn wọ̀n tán, ohun tí ó kù ni kí á máa ní ire gbogbo. Ire máa ni ìgbẹ̀hìn ẹni tí ó ṣọ̀ ori rere, tí ó fi ọgbọ́n àti ẹsẹ̀ ṣe aṣeyan, tí ó fi àyà yan ọ̀rẹ́ tí ó ní láári, tí ó sì tún rúbọ. Ìdí nìyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹsẹ Ifá fi máa ń pari pẹ̀lú ọ̀rọ̀ nípa ire. Fún àpẹẹrẹ, ẹsẹ Ifá kan parí pẹ̀lú:

Ìrù ẹbọ,
Àtètè ru ẹ̀rù,
Ẹ wáà bá ni ní jẹ̀bútú ire.

Ìtumọ̀ èyíi ni pé kí gbogbo ayé ó wáá wo ẹni tí ó rúbọ, tí ó sì ru ẹ̀rù ìdí tí ó tí ń ni ire gbogbo. Ẹsẹ Ifá mìíràn tún parí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

Ìrù ẹbọ ni í gbe ni,
Àìrú kì í gbèèyàn.
Ẹ wáà bá ni ní wọ̀wọ̀ ọmọ.

Ìtumọ̀ èyí ni pé kí àwọn ọmọ aráyé ó wáà bá ẹni tí ó rúbọ láàrin ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ.

Irú kín ni àwọn Yorùbá ká sí ire? Gbogbo nǹkan dáradára tí ọmọ aráyé ń lépa láyé ni àwọn Yorùbá ń pè ní ire. Àwọn ni nǹkan bí ilé, aya, owó, aya, ọmọ, àti àláfíà. Nípa ti ilé, ẹsẹ Ifá kan sọ nínú Èjì Ogbè pé:

Bé niyí bam ayo ó,
Bé níyí òun ọmọ,
Eéyàn èé ṣe fóju laínilé.
Bé níyí òun ọmọ.

Nínú gbogbo ire ilé ayé yìí pátá pon, mẹ́ta l'ó ṣe pàtàkì jù. Àwọn ire mẹ́ta mìí ni ire owó, ire ọmọ, ire àìkú (tàbí àlàáfíà) parí ìwà. Ó ní:

Ire mẹ́ta l'àwá ń wá,
Àwá ń wówó o,
Àwá ń wọ́mọ,
Àwá ń wá àtubọ̀tán ayé.



Ẹni tí ó bá ti ní àwọn ire mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí ti ní iyókù. Ẹni tí ó bá lówó lọ́wọ́ yóò níyàwó, yóò kọ́lé, yóò sì ní aṣọ. Ìdí nìyí tí owó fi jẹ́ ẹ̀gbọ́n fún gbogbo ire yòókù. Àwọn baba wa l'ó máa ń pòwe wí pé 'Owó lẹ́gbọ́n, ọmọ làbúrò.'

Ṣùgbọ́n bí ènìyàn ti wà kí ó lówó tó, kò lee rí ọmọ rà lọ́jà, bẹ́ẹ̀ sì ni kò lee fowó ra ẹ̀mí kún ọjọ́ ayé rẹ̀. Ìdí nìyí tí ire ọmọ àti ire àìkú fi ju ire owó lọ nígbẹ̀hìn. Ó ní:

Ọ̀rọ̀ọ̀rọ̀ọ̀rọ̀, babaláwo olówó l'ó dífá f'olówó,
Ọ̀rọ̀ọ̀rọ̀ọ̀rọ̀, babaláwo ọlọ́rọ̀ l'ó dífá f'ọlọ́rọ̀,
K'á jọwà tán, k'ó gbọn'wọ̀ ẹsẹ̀ nù àwo poro poro,
Babaláwo ọlọ́mọ l'ó dífá f'ọlọ́mọ,
Erò Òkun,
Erò Ọ̀sà,
'Ta ni ó mọ̀ pé ìpa ọlọ́mọ ò ní í parun.

Ohun tí Ifá ń wí nínú ẹsẹ yìí ni wí pé ìrànlọ́ ẹni tí ó fi ọmọ s'ilé ayé yóò máa wà títí ayé ni. Ìṣẹ́ tí ó dámọ̀ kí tàbí ohun tí ó dùnú fún ó máa gbé sí i ni nínú ìgbà tí ó bá ti fi ọmọ rere sílẹ̀ láyé. Àwọn tí ó máa ń pòkú l'ó máa ń wí pé:

Òkú olówó,
Ọgù mèje.
Òkú ọlọ́rọ̀,
Ọgù mẹ́fà,
Òkú ọmọ́nìyàn,
Ó máa d'ẹgà t'á ó mayo.

Ire àìkú l'ó parí gbogbo nǹkan láyé. Níbori mìí, òun l'ó ṣe pàtàkì jù. Ẹni tí ó bá ní ẹ̀mí gígùn pẹ̀lú àlàáfíà ara láyé, kò sí nǹkan tí kò ká jù. Bí kò bá tètè ní àwọn ire yòókù lákọ̀ọ́kọ́, nígbà tí ó bá pẹ́, á ní gbogbo wọn bí ó bá ti yan ìrú orí bẹ́ẹ̀, tí kò sì ṣe ọ̀lẹ. Ṣùgbọ́n bí èèyàn bá ní àwọn ire yòókù, ṣùgbọ́n tí kò pẹ́ láyé ńkọ́, bí aláìwá sáyé rárá ni. Ẹni tí ó pẹ́ láyé, tí ó sì fi àlàáfíà lo ẹ̀mí gígùn nǹkan l'ó gbádùn ayé. Ìdí nìyí tí Ifá fi sọ wí pé àìkú l'ó parí ìwà. Ó ní:

Kòì pẹ́ o,
Kòì jìnà,
Ẹ tètè wáà bá ni ní àìkú kangiri.
Àìkú kangiri là á bá ní ẹsẹ̀ Ọbarìṣà.

(vii) *Àkíyèsí nípa ìsìn.* Àìpẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìtí alákíyèsí ni Ifá. Nítorí náà ẹsẹ Ifá kún fún àkíyèsí nípa àwọn ẹ̀dá orílẹ̀-èdè. Irú àkíyèsí yìí bẹ̀rẹ̀ láti orí àwọn ẹranko inú igbó bí erin, ẹfọ̀n, ẹtu, àgbọ̀nrín àti àwọn tí ó fi dé orí àwọn ẹyẹ bí igún, àkàlà, ìgà, ẹyẹlé, adìẹ àti òròrẹ̀.

Ifá tún sọ ọ̀rọ̀ nípa àwọn kòkòrò bí aláǹtakùn, yíndinyíndin, èèrùn, ìkamùdù àti èèrà. Bákan náà ni ẹsẹ Ifá kún fún àkíyèsí nípa àwọn igi inú igbó bí ìrókò, ìrúmọ̀gbò, osè, àràbà, omìrà àti àpá. Ifá sì tún sọ ọ̀pọ̀ nǹkan nípa àwọn igi tí a ń gbìn bí ọ̀wú, àgbàdo àti obì gbànjà. Ifá kò kẹ̀rẹ̀ nípa àkíyèsí lórí àwọn nǹkan tí kò ní ẹ̀mí bí òkè, odò, òkúta àti ojú-ọjọ́ pẹ̀lú. Kò sí nǹkan kan tí a bá ní ilẹ̀ Yorùbá tí Ifá ò rí wí nípa rẹ̀. Nítorí, a ó sọ díẹ̀ nípa irúfẹ́ àwọn àkíyèsí wọ̀nyí tí a máa ń bá pàdé nínú ẹsẹ Ifá.

*Àwọn ẹranko inú igbó.* Ifá sọ̀rọ̀ púpọ̀ nípa àwọn ẹranko inú igbó. Fún àpẹẹrẹ, Ifá sọ̀rọ̀ nípa àáyá àti ẹdun nínú Èjì Ogbè nínú ìwé yìí níbi tí a gbé sọ wí pé:

Aré l'ó bá ẹdun ńlẹ̀,
Ẹdun ò mọ̀ọ́ sá,
A dífá fún ẹdun tí í ṣe ọmọ ìyá ààyá. . . .
Aré l'ó bá ẹdun nílẹ̀,
Ẹdun ò mọ̀ọ́ sá,
Aré orí igi l'ó yẹ ẹdun.[37]

Nítorí, Ifá ò ṣe àkíyèsí pàtàkì nípa ẹdun àti ààyá. Ifá ń sọ nínú ẹsẹ yìí pé bí a tilẹ̀ jẹ pé ọmọ ìyá kan náà ni ẹdun àti ààyá, ṣùgbọ́n wọn kò fi ìwà jọ araa wọn. Ifá tún ń sọ wí pé lórí igi nìkan ni ẹdun gbé le sáré mọ, bí ẹdun bá ti dé ilẹ̀, kò lè sáré mọ́. Èyí ni ó fi ń dààmú nígbà tí a bá ń sọ wí pé Làgbàjá tí di ẹdun arínlẹ̀.

*Àwọn ẹranko ilé.* Ifá sọ ọ̀pọ̀ nǹkan nípa àwọn ẹranko ilé bí ajá, ewúrẹ́, àgùtàn, màlúù, ẹṣin àti àgbò. Ẹsẹ Ifá kan ṣe àlàyé pé tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ rí ni ayé àtijọ́, ajá ni ọmọ ìgbẹ̀yìn Òwu. Ọ̀rẹ́ pàtàkì sì ni òun àti Olówu, ṣùgbọ́n nígbà tí ó di ọjọ́ kan ni àìsàn bá kọ lu Olówu, ajá sì lọ wò ó. Wọ́n jọ jẹ àjẹtọwọ́gbọwọ́ ki ajá ó tóó padà s'ílée tirẹ̀. Kò pẹ́ tí ajá kúrò n'ílé Olówu, ni Olówu bá mí kanlẹ̀, l'ó bá kú. Ni wọ́n bá lọ mú ajá pé òun l'ó nu ọ̀rọ̀ rẹ̀ lóògùn. Ìgbà wí pé òun kò mọ̀ sí ikú Olówu ni ajá ń kè lórí dúnì nígbà tí ó bá ń gbó, tí ó ń wí pé 'òun ò mọkú t'ó kúkú pOlówu'.

*Àwọn ẹyẹ oríṣiríṣi.* Ifá sọ̀rọ̀ ẹ̀pẹ̀ẹ̀rẹ̀ nípa ẹyẹ ilé àti ẹyẹ oko. Ẹsẹ Ifá kan láti inú Èjì Ogbè nínú ìwé yìí ṣe àlàyé bí ẹyẹlé ṣe kúrò ní oko tí ó fi di ẹni tí ń gbélé. Ifá ń sọ fún wa nínú ẹsẹ yìí pé nígbà tí ẹyẹlé fi ń gbóko yìí, ó yàgàn. Nígbà tí ó wáá lọ sọ́dọ̀ Èjì Ogbè tí Odù yí ṣe ètùtù fún un l'ó bá lóyún, ó sì bí ọmọ jẹ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Látì ìgbà náà ni ẹyẹlé ti ní kò padà sí oko mọ́, tí ó sì ń gbé ọ̀dọ̀ Èjì Ogbè. Òun l'ó mú ó ṣàlé dè Èjì Ogbè nígbà tí Odù yí kò bá sí nílé. Idí kan nìyí tí wọ́n fi máa ń yà ẹ̀ro ẹyẹ sí ara ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ tí àwọn àgbà awo máa ń mú kọ̀wú. Èyí ni Ifá ń ṣíkaá sí nígbà tí ó wí pé:

Olómimorò, tún'lé ṣe dè mí ò,
Ẹyẹ tún'lé ṣe.
Ẹrúkuku tún'lé ṣe dè mí ò,
Ẹyẹ túnlé ṣe.

*Àwọn kòkòrò oríṣiríṣi.* Ifá sọ ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ lórí àwọn kòkòrò bí aláǹtakùn, èyí tí Ifá pè ní 'ọmọ aṣọdun gbogbo bí kẹ̀tẹ̀, bí ìdan' àti 'olùgìmìnigan ìjàkùn . . . t'ó tí ó rín lágàn, yóò l'ọmọ ìmọdí'. Ẹsẹ Ifá kan sọ wí pé aṣọ ẹdun ni iyẹ tí a bẹ lára ààyán. Ṣùgbọ́n nítorí ìfọ̀jàdì rẹ̀, bí ó bá ti fi aṣọ yìí gbálẹ̀ gẹrẹrẹ níbi tí àwọn ẹyẹ yóókùú wà, pípa ni wọ́n máa ń pa á jẹ. Ọ̀rúnmìlà ní:

Ó di ẹ̀kẹ́ ẹkọ,
Ẹ̀kọ̀ọ̀ Ifá;
Ààyán kò gbọdọ̀ f'aṣọ ẹdun gbálẹ̀ gẹrẹrẹ nígbàjò ẹkẹyẹ.

*Àkíyèsí nípa àwọn nǹkan aláìlẹ́mìí.* Ifá sọ̀rọ̀ nípa irú àwọn nǹkan wọ̀nyí náà. Òkúta ni alápàá mọ̀ ṣìṣẹ̀. Òkè ni ọlọ́mọ àkàyèkàà tàbí ọlọ́mọ ìyan ìyan gidigbá. Òkè náà ni a tún ń pè ní ẹni mọ̀ ó kà. Ifá ní:

Ogún ẹdun ìnú ń,
Òkè ń bẹ lókè gbọin gbọin.
Gbọin gbọin ni tòkè.
Òkè, òkè gbọin gbọin . . .
Ìgbà gbogbo lòkè ń bẹ lókè gbọin gbọin.
Gbọin gbọin ni tòkè.
Òkè, òkè gbọin gbọin.[38]

## 6. Bí a ṣe kó ìwé yìí jọ

Mo gba gbogbo ẹsẹ Ifá tí ó wà nínú ìwé yìí láti ẹnu Oyèdèjì Ìgàlà àti Adéjàre Kékeré-awo, ilé Ìlọ̀ọ̀ṣìn, Pààkòyí Ọ̀yọ́. Oyèdèlé jẹ́ gbajúmọ̀ babaláwo ní ìlú Ọ̀yọ́. Ó tó ẹni àádọ́ta ọdún báyìí. Adéjàre jẹ́ ẹni ọdún méjìdínlógójì. Àwọn méjèèjì jọ ń ṣawo pọ̀ ni.

Mo gba ọ̀rọ̀ ẹsẹ Ifá wọ̀nyí lẹ́nu wọn ní nǹkan bí ọdún mẹ́tàlá sẹ́yìn báyìí. Ní ìlú Ọ̀yọ́ ni mo ti gbà wọ́n sílẹ̀. A gba díẹ̀ nínú ẹ̀rọ tí a fi ń gba ohùn sílẹ̀, mo sì tún fi ọwọ́ kọ díẹ̀ nínú ìwé pẹ̀lú.

Ní nǹkan ọdún 1969 ni mo ti da àwọn ẹsẹ Ifá wọ̀nyí kọ tán, mo sì ṣe ọ̀nkọ ìwe tí ó kọ wọn sí ní *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kẹta. Ṣùgbọ́n ní ọdún tí ó kọjá yìí ni mo rò ó wò wí pé ó yẹ kí ìwé yìí ó yàtọ̀ gédégédé sí àwọn ìwé Ifá mẹ́jẹ̀ẹ̀jì tí a ti tẹ̀ jáde tí à ń pè ní *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní àti Apá Kejì. Ohun tí ó fa èyí ni wí pé mo ṣe àkíyèsí wí pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kan ń ka àwọn ìwé mẹ́jẹ̀ẹ̀jì ni, wọn ó mọ ìtumọ̀ ohun tí ó wà nínú wọn.

Nítorí náà, ó yẹ kí à ní ìwé mẹ́jì tàbí mẹ́ta kan nibi tí a ó ti ṣe àlàyé ẹsẹ Ifá kọ̀ọ̀kan dáadáa kúnnà. Lẹ́yìn tí a bá ti ní irú ìwé báwọ̀nyí, bí a tilẹ̀ tí tẹ ìmíràn jáde tí kò ní àlàyé púpọ̀, àwọn ònkàwé náà ó máa fi ọgbọ́n gbé e nítorí pé wọn ti ní èyí tí wọn ó fi máa dìwọn èrò inú wọn.

Ìdí nìyí tí a fi kọ ìwé yìí jọ ní ọ̀nà yí. Ẹsẹ Ifá tí ó wà nínú ìwé yìí jẹ́ àkàtọ́jẹ-ò-dìn-mẹ́jì. Gbogbo ẹsẹ Ifá wọ̀nyí l'a sì ní àlàyé ti wọn bí ó ti wù kí ó kéré tó.

Mo lérò wí pé àwọn ònkàwé yìí ó gbádùn àwọn ẹsẹ Ifá tí a kọ jọ sínú ìwé yìí àti àwọn àlàyé tí a ṣe lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

WANDE ABIMBỌLA

*Department of African Languages and Literatures*
*University of Ife*
*ILE-IFẸ*

## ÀLÀYÉ ÒRÒ

1 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, Collins, Glasgow, 1968, p. 46.
2 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 45.
3 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 45.
4 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 46.
5 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, pp. 45–6.
6 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kejì, Collins, Glasgow, 1969, p. 85.
7 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kejì, p. 48.
8 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kẹta, Mimeographed, University of Lagos, 1970, p. 13.
9 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 150.
10 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 111.
11 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 139.



12 *Àpólà Ọgbè*, Apá Kìíní, mimeographed, University of Lagos, 1970, pp. 134–5.
13 *Àpólà Ọgbè*, Apá Kìíní, pp. 277–8.
14 Wo ojú ìwé 5.
15 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 89.
16 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 131.
17 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 132.
18 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 112.
19 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 25.
20 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kejì, p. 87.
21 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, pp. 113–15.
22 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, pp. 73–4.
23 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, pp. 143–4.
24 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kejì, p. 84.
25 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kejì, p. 98.
26 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kẹta, pp. 3–4.
27 Wo ojú ìwé a tàbí ìdó 3.
28 *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá Kìíní, p. 31.

Ţoạ Hà Kộgkan

## 1 ÈJÍ OGBÈ

### Ese Ẹ̀kínì

Arí l'ó b'ẹdun ẹlẹ̀,
Ẹdun ò mọ̀ ọ̀n sá;
A dífá fún ẹdun,
Ẹdun tí í ṣe ọmọ iyá ààyá.
Ààyá fò fẹ̀rẹ̀,
Ó g'orí igbá.
Ẹdun ta fẹ̀rẹ̀,
Ẹdun g'orí igi.
Nígbà tí iwà ṣẹ,[1]
Ọ̀rọ̀lẹ̀ ni ààyá máa ń rìn
Òun pẹ̀lú ẹdun,
Ọmọ iyá ẹ̀.
Ṣùgbọ́n ní ọjọ́ kan,
Ẹdun àti ààyá wáá jáde,
Wọ́n lọ jí ìgbàdo ya l'óko olóko.
Ààyá l'ó kọ́ rí olóko,
L'ó bá fò fẹ̀rẹ̀ gun igi igbá.
Nígbà tí ẹdun ó fi wí pé òun ó fò,
Olóko ti dé,
Ó sì mú ẹdun.
Olóko wáá di ẹdun lókùn
Nígbà tí ó mú un dé ilédì,[2]
Wọ́n rí i pé ọmọ Ọ̀ṣun ni.
Wọ́n wáá sọ fún olóko pé
Ẹni tí o mú wá yìí,
Àwọn ò gbọdọ̀ pa á,
Nítorí pé ọmọ Ọ̀ṣun ni.
Wọ́n ní kí ẹdun ó jẹ́wọ́.
Ni ẹdún bá jẹ́wọ́,
Ó ní lóòótọ́ ni òun ya ìgbàdo,
Ṣùgbọ́n lọ́gí olóko ni òun ṣe ya á.
Wọ́n wáá ní ẹdun pé

Kò ní yóò nu fún olóòn.
Ẹdún wáá bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe bíi wèrè.
Ó ní, 'Ẹdún yàgbàdo bàà;
Ẹdún yàgbàdo bàà.'
Ní òwọn ẹgbẹ́ ìmọ̀lẹ̀ bá ṣe wí pé
'Ti ẹdún tán ńbì,
Wọ́n ní àìyà ti ó rí olóko sá
Ní bí wọn ó ti ìyà jẹ.
Wọ́n ní, 'Ọmọ bá kan mà
Ní ẹdun àti àìyà.
Ṣìgbọ́n wọn ó fi ìwọ̀ jọrọ wọn.
Ẹdún bọ́ nínú ẹjọ́,
Ọràn sì kan àìyà.'
Àwọn Ògbóni wáá ní
'Ta ni ó tàntàn aran wọn?'
Wọ́n ní, 'Ìrọ ẹdun,
Nígbà tí o mọ bwà àìyà,
Èé ṣe tí ẹ ó jọ fò fẹ̀rẹ̀?
Ẹdun gbàlájà, ewo l'o wáá sárè ṣe?
Kín l'ó ṣe tí o ó fi fò mọ́gi?
'Tí olókoo fi wáá mú ọ?'
Ẹdún ní, 'Ọmọdé ni í yára bí òpá,
Àgbà ṣbíkím dẹ́rẹ̀ bí àpò.
Arò lògdon ńlẹ̀,
Ẹdun ó mọ̀ ọ̀n sá.
Arè-sọ́ ìgì l'ó yé ẹdun.'
Àìyà wá ń fò sókè.
Ẹdún wá ń bẹ̀:
Àìyà fò sókè,
Ẹdún bẹ̀.
Àìyà fò mọ́gi lọ́rùn,
Ẹdún ṣì,
Ẹdún lọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀keji

Ní ọjọ́ tí Ìlègún dé ayé,
Ẹ̀keji ni wọ́n tú i,
Ọ̀kán bá, ọ̀kán wá bàayé.

Ẹ̀yì tí ó wá bàayé wáá mankùn tìtì,
Ní wọ́n bí dójgbọ́n,
Wọ́n d'ìṣọ Ẹ̀rgún.
Wọ́n mú ẹ̀yì tí ó wá bàayé lọ sínú igbó,
Wọ́n gbé ọmọ Ẹ̀rgún nàà lọ ọ̀ṣìkan bìrì.
Ẹni tí ó gbé Ẹ̀rgún nàà ó pe
Ẹ̀yì tí ó wá bàayé pé:
'Má tẹ̀ ṣá o,
Ìhìn ó yọ̀ o à.'
Ẹ̀yì tí ó wá bàayé bẹ̀rẹ̀ sí í sunkún,
Ẹ̀rgún nàà yára wọ inú igbó lọ.
Àṣọ tí a dà bo aláàyè bìrì
Ni à ń pè ní ẹ̀kú Ẹ̀rgún.
Ẹ̀kú ayé o,
Ẹ̀kú ọ̀run,
Ni à ń pè ní ẹ̀jigbèdè ẹ̀kú.
Ní ọjọ́ kan,
Iyá Ẹ̀jì ń wá,
Ẹ̀rgún sì ń bọ̀ wá,
Ẹ̀rgún gbé aṣọ iyá ẹ lọ.
Wọ́n ní, 'Kín l'ó gbé ọ l'áṣọ lọ?'
Ó ní, 'Àìmọ̀ ni ẹ́.'
Wọ́n ní, 'Kín ni í jẹ́ àìmọ̀?
Ó ní, 'Ẹ̀kìní ni Ẹ̀rgún,
Ẹ̀keji Orò.
Bí ẹ̀rgún ó bá mọ́ọ̀ wá,
Ta ni ó gbéè aṣọ lọ ẹ lọ?'
Wọ́n ní kí wọ́n ó bí Ẹ̀rgún.
Ẹ̀rgún ní òun ó gbé e.
Wọ́n ní kí wọn ó bí Orò.
Orò ní òun ó jalè.
Wọ́n ní kín ni kí aya Ifá ó ṣe?
Wọ́n ní bí Ifá bá ṣe Ẹ̀ṣù
Ta ni ó ó wáá gbẹ̀bọ l'ọ́wọ́ Ọ̀gun?
Orò yára mú aṣọ aya Ọ̀rúnmìlà wá.
Ifá mú jẹ̀
Kí wọn ó gbé aṣọ ìdìì ni lọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Òfúfú ni í pẹrẹ̀;
Ẹ̀pẹ̀ ni í polẹ̀;
Ilẹ̀ dídà ni í pọ̀rọ̀;
Akíjọ̀bà ni í pàyekan t'ó ṣebi.
Àṣẹ d'ọwọ́ ilẹ̀ a jẹ mu;
A díá fún ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀
Nijọ́ tí wọn ń jẹ̀ r'ọ̀dọ̀ Olódùmarè.
A jẹ gb'óri ilẹ̀,
A jẹko.
A jẹ gb'óri ilẹ̀,
A jẹja.
A jẹ gb'óri ilẹ̀,
A jẹran.
A jẹ gb'óri ilẹ̀,
A jẹ kókó ìgbín.
Àṣẹ d'ọwọ́ ilẹ̀ a jẹ mu.
Njẹ mo dúpẹ́ tèmi o,
Ẹ̀jì kiribiti, ọmọ Ẹlẹ́mẹ̀rẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹ̀jìgbèdè gbìgbè ni o gbé mi;
A díá fún Òjúoró
Tí ń lọ ìsàlẹ̀ ìbòtà,
Tí ń lọ rèé kanrilẹ̀ ọmọ ní bíbí.
Ẹ̀jìgbèdè, ẹyẹlẹ́ ó ṣakọ, ó ṣabo,
Wọn a jùmọ̀ jẹran wọn,
Láìjìmọ̀ yàtọ̀;
A díá fún Ẹ̀jìgbèmí
Tí í ṣe ọmọ ìyàá Mọ́yàmọ̀yà.
Ẹ̀jèèjì ni mo gbé,
Ng ó gb'enìkan ṣoṣo mọ̀;
A díá fún Ẹyẹko
Nijọ́ tí ń bẹ láàrin ìgbẹ́.
Nígbà tí Ẹyẹlẹ́ ó ṣorkún
[illegible]
Wọn ní ẹ̀yẹ ni ki ó wáá l...
Ó sì rú u.



Nígbà àlẹ̀lẹ̀ rí,
Wọn kì í pe ẹyẹlẹ́ ní ẹyẹlẹ́,
Ẹyẹko ni wọn ń pè é,
Nítorí pé oko ni ó gbé.
Ọmọ ìyá ni òun àti àdàbà.
Ooni, ọmọ ìyá ẹyẹlẹ́ ni òun ìdá pẹ̀lú.
Gbogbo wọn l'ó bímọ,
Ẹyẹlẹ́ nìkan ni ò bí.
Ó wáá tọ Ẹ̀jì Ogbè lọ.
Ẹ̀jì Ogbè ní k'ó rúù àgbàgbà ààdìpọ̀ méjì,
Ẹku méjì, ẹja méjì, ẹyindẹ méjì,
Kí ó fi gbogbo rẹ̀ rúbọ.
Ẹyẹlẹ́ sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Nígbà tí ẹyẹlẹ́ ó parọ,
Méjì l'ó pa.
Ó wáá kó àwọn ọmọ náà lọ Ẹ̀jì Ogbè,
Ó dúpẹ́, ó sì tún mọ ẹ̀jẹ̀ẹ̀gùn.'
Ó ní láti fi ìmoore òun hàn,
Kí Ẹ̀jì Ogbè ó kọ́ọ̀ fún òun
Ní ìtan rẹ̀,
Kí òun ó máa gbé.
Ó ní, 'Mo bímọ méjì,
Mo d'ẹyẹ ilé.
Mo bímọ méjì,
Mo d'ẹyẹ ilé.'
Ẹ̀jì Ogbè ní ẹyẹ yìí yẹ ilé kíkàn.
Ni wọn bá fi ń pè é ní ẹyẹlẹ́.
Ó ní kí ẹyẹlẹ́ ó fi ọ̀kan
Tì kó bá fẹ́ nínú àwọn ọmọ náà rúbọ.
Ẹyẹlẹ́ ní, 'Ng ò le fi'kan rúbọ o,
Ẹ̀jèèjì ni mo gbé,
Ng ó le pà'kan;
Ẹ̀jèèjì ni mo fẹ́rán.'
Ni Ẹ̀jì Ogbè bá fi àṣẹ sí i pé
Méjìméjì l'ẹyẹlẹ́ ó máa bí
Nígbàkùgbà tí ẹyẹlẹ́ ó bàá parọ.

## Ese Ëkaàrín

Oyinkangí:
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà
Nígbà tí Ifá ń lọ rèé f'ẹ̀ta ọgbọ̀n kanrí.
Ní ọjọ́ tí Ọ̀rúnmìlà ń lọ réé bá ikú mulẹ̀
Pé kí ó má bá ọn ìsun ní kékeré.
L'ó bá lọ bá Oyinkangí
Pé kín ni òun ó ṣe.
Oyinkangí ní kí ó tọ́jú ogbógbó mọ́ṣẹ̀,'
Ori, ọṣẹ, kí ó sì ba ẹ̀rúpẹ̀ idí ìkẹ́,
Kí ó sì tọjú irin.
Kí ó fi gbogbo rẹ̀ rúbọ nítorí ikú.
Ọ̀rúnmìlà ní,
'Njẹ́, mo d'ogbógbó mọ́ṣẹ̀,
Ng ó kú mọ́.
Mo d'igba ìkẹ́,
Mo lé gbọnyin.
Gbogbo nǹkan ni ng ó mọ̀.
Gbogbo nǹkan tí ọrun àti ayé
Ni ng ó rí.
Ng ó sì mà yẹ ọmọ mi mọ́.
Fọrú ni mo dákẹ́;
Mo rin rìn rin,
Ng ó sọnù.'
Wọ́n ni kí wọn o wá ibi wá.
Ọjọ́ mi ò ní í rìbí.
Ọ̀rúnmìlà ń lọ lọ́nà,
Afẹ́fẹ́ ń kó aṣọ aláṣọ;
Ẹ̀fúùfù lẹ̀lẹ̀ ó ké ọ̀rọ̀.
Wọ́n ni àwọ Ọ̀rúnmìlà,
Báwo ni òwọn ó ti ṣe wá a?
Ọ̀rúnmìlà ní ará ọrun l'ẹ ń rí.
Wọ́n ní àìrí lọ́rà.
Ogun ayé àti ogun ilẹ̀
Ni wọ́n dá lọ́rán ní ilú afẹ́fẹ́,
'Tí afẹ́fẹ́ fi ń gbé wọn lọ.
Afẹ́fẹ́ ni oriko à á pe Orò.
A ó bá sí Orò,
Afẹ́fẹ́ ni kí e máa kó sí.



Olum [illegible] Fá à pẹ̀rọ̀,
Ifá ní ọjọ́ à mi ó ní í rìbí.

## Ese Ëkẹfà

Ìwàjú òkun,
Òkun ni wọ́ọ́n ṣe;
Ẹ̀yìn òkun,
Òkun ni wọ́ọ́n ṣe;
Ẹ̀rìn kò ṣeé yí padà kan,
Abátà kan kúún kun;
Lókun kíkan l'á á kì ọmọ ọkọ̀ já mọ́ńrọ́ndíńbígún;
L'ó dífá fún wọn l'ode Ìdó;
Ará òde Ìdó
L'ó dífá fún wọn l'ode Ìgẹ́tí.
Ní ọjọ́ tí wọ́n jí ní kùtù,
Wọn ń sunkún àwọn ò ní ọ̀bà
Ọjọ́ọ́jọ́ọ́ ìwọ́gun ń kó wọn mọ́lẹ̀ gìrìgì.
Wọ́n ní kí àwọn ará òde Ìdó ó rúbọ,
Kí wọn ó lè bá lọ́bà,
Kín ni àwọn ó lọ rú báyìí?
Wọ́n ní kí wọn ó rú ìgbà ìgbìtàn kan,
Ọ̀pọ̀lọpọ̀ epo pupa, obì ifin ogójì,
Obì ipa ogójì, ẹgbàá mẹ́wàá,
Ìlẹ̀kẹ̀ itú, ìlẹ̀kẹ̀ ifà,
Pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ aṣọ́ẹ̀fun.
Wọ́n ní kí wọn ó kó gbogbo rẹ̀ sínú igbádà,
Kí wọn ó gbé e lọ sí etíkun,
Wọ́n sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Wọ́n ní bí wọ́n bá dé etíkun,
Ẹni tí wọ́n bá kọ́ rí nibẹ̀,
Ni kí wọn ó mú,
Kí wọn ó fi jọba Ìdó.
Nígbà tí wọ́n dé etíkun,
Wọ́n bá ẹnikan níbẹ̀,
Wọ́n yára mú un,
Wọ́n fi jọba.
Ìgbà tí inú wọ́n dùn tán,
Orin ni wọ́n ń kọ.
Wọ́n ní, 'Ìwàjú òkun,

Òkun ni,
Ẹyin ikun,
Òkun ni.
Èèyàn t'ó mùpin ikun kò sí.'

## Ẹsẹ Ìkẹjẹ

Abẹ̀rẹ̀ mú tojútimú;
Wọn a ṣèdì gbọ̀dọ̀;
Wọn mú agbede méjì ṣe bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀;
A dífá fún Ẹrin,
Wọn ò ó mérin jọba ìlú Àṣo.
Abẹ̀rẹ̀ mú tojútimú;
Wọn a ṣèdì gbọ̀dọ̀;
Wọn mú agbede méjì ṣe bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀;
A dífá fún Ùlọ̀n,
Wọn ó mú un jọba ìlú Àjànà.
Abẹ̀rẹ̀ mú tojútimú;
Wọn a ṣèdì gbọ̀dọ̀;
Wọn mú agbede méjì ṣe bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀;
A dífá fún Jakumọ,[7]
Wọn ó ó mú un jọyè Alàpatà Oko.
Abẹ̀rẹ̀ mú tojútimú;
Wọn a ṣèdì gbọ̀dọ̀;
Wọn mú agbede méjì ṣe bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀;
A dífá fún Òtòlò,
Wọn ó ó mú un jọyè Olú Oko.
Ẹrù Ìpo,
Ẹrù Ọ̀fà,
Orí l'ó a'ọ̀kùn d'olókn.

## Ẹsẹ Ìkẹjọ

Igbó biribiri;
Òkùnkùn birimù birimù;
Ẹrù ó bá mọ̀ọ̀ṣe òkùnkùn,
K'ó mọ̀ mọ̀ d'ọ̀ṣùpá lèé,
Olóun ṣeni à á rìnrìn;
Òkùnkùn kò yẹ ọmọ èèyàn;
A dífá fún Ọ̀gbè-ṣooro-gbìkà
Tí wọn ó máa ran ìbi fún dípò oore.



Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó ṣe.
Wọ́n ní kí ó lọ bọ́ ìlú ọ̀gọ̀dọ̀,
Kí ó ṣe oró ìkú lé e lórí;
Kí ó wé e ní aṣọ bí òkú,
Kí ó gbọ́ọ̀ ibi tí èèyàn lè sin òkú sí
Ní ààlà oko,
Kí ó wá dà sùrì lé ọ̀gọ̀dọ̀ náà
Nínú ibi tí ó ti gbẹ́.
Kí ó sin in bí ẹni sin òkú.
Ó sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Ìgbà tí àmì rẹ̀ dùn tán
Orin awo ní ó kọ,
Ó ní, 'Ru rere o,
Ìkà, ru rere.
Olun tí ọ̀gọ̀dọ̀ ṣe l'ìgbẹ̀ l'ó pọ̀,
Ru rere,
Ìkà, ru rere.'

## ATÚMỌ̀

1 *Nígbà tí ìmà yí*: Nígbà tí Olórun kò ṣe ẹ̀dá ayé.
2 *Ìtòdì*: Ojú ìpàdé awọn Ọ̀gbóni.
3 *Ṣan ẹ̀gẹ̀gẹ̀*: ṣan owó fún aṣẹ̀gun nígbà tí a rí i pé lóòótọ́ ni ó ṣe fún wa ni jẹ́, tí ó sì bá wa fàra rẹ̀.
4 *Ọ̀yọ̀ọ̀kọ̀ọ̀*: orúkọ òrìṣà kan.
5 *Ọ̀gbẹ́gbẹ́ ọ̀rún*: àlọ́ kan.
6 *Àgbà àgbààlẹ̀*: àgùntàn ọlà kan.
7 *Jàkùmọ̀*: Ẹran ìnú ìgbẹ́ kan tí ó fara jọ ọ̀kàn.

2

# Ọ̀YẸ̀KÚ MÉJÌ

## Ẹsẹ Èkínní

Ọ̀yẹ̀kú, mo bá ọ mulẹ̀,
Mọ̀ mọ̀ ṣe dà mí.
Ìmí bíbí ẹrú ní í pẹrù;
Ẹdọ̀ fúfú ìwọ̀fà ní í pa ìwọ̀fà;
A díá fún Odùdùwà.[1]
Nígbà tí ó bẹ láàrin ọ̀tá ọ̀yẹ́.
Bí ikú bá ó ṣí ẹgbẹ̀ẹ̀ mi pa,
Ọ̀tọ̀ ni Ọ̀yẹ̀kú ó mọ̀ ṣá mí sí.
Bí àrùn bá ó ṣó ẹgbẹ̀ẹ̀ mi ṣe,
Ọ̀tọ̀ ni Ọ̀yẹ̀kú ó máa gbé mi sí.
Gbogbo àlùwẹ̀ obì ni ikú pa,
Ọ̀tọ̀ ni à á yọ oníùà obì sí.
Ikú má pawo mọ́ o,
Ikú tí yọ̀ lórí awo;
Ọ̀tọ̀ ni à á y'oníùà obì sí.
Ikú má pawo mọ́ o,
Ikú yọ̀ lórí awo.

## Ẹsẹ Èkejì

Bí o bá yọ̀,
Èmi ó yọ̀;
Yangí ilẹ̀, wọn ò gbọdọ̀ yọ̀lẹ̀;
Àtàrí wọn ò gbọdọ̀ yẹ ẹrù ọjà;
A díá fún Ọlọmọ Akoto,
Tí ń ṣawoò lọ sí ìlú gbẹ́ndú gbẹ̀ndu.
Wọ́n ní iwọ Ọlọmọ Akoto,
Wọ́n ní ìlú gbẹ́ndú gbẹndu
Ni ó ń ṣawoò lọ yìí,
Wọ́n ní o ò gbọdọ̀ lọ.
Wọ́n ní bí yóò bá ṣì lọ,
Wọ́n ní kí ó rúbọ àkàdà
Wọ́n ní kí ó rú eku méjì olúwẹ́wẹ̀;
Kí ó rú ẹja méjì olúgbààlẹ̀;
Ẹyẹ méjì abìfò gẹ-ngẹ;
Ewúrẹ́ méjì abàmú rẹ̀dẹrẹ̀dẹ.
Ó rúbọ tán,
Wọ́n ṣe Ifá fún un.
L'ó bá kọri sí ìlú gbẹ́ndú gbẹ̀ndu.
Ó ní kí ajé ó yalé wá,
Kí ó wáá jẹun.
Ńjẹ́, ajé ya'lẹ̀ wá wá,
Kí o wáá j'ẹran ògẹ̀dẹ̀.
Ẹran ògẹ̀dẹ̀ ni mo sè sílẹ̀ dọ́.

## Ẹsẹ Ẹkẹta

Abìlẹ̀rọ̀, abìlẹ̀ralẹ̀,
Abọmọ gbogbo lóhun lóhun;
A díá fún Ọbìlìn[2] Àyìngbò,
Tí ń rayé Ilàkù.
Ng ó rúùgbó o,
Ìbẹ̀ẹ̀ ni ng ó kú mọ́.
Ng ó rúùgbó Ọlọ́run mọ́ ìkùn.
Àjàṣẹ̀rìn, Ọlọ́run mọ́ ìkùn.
Ẹ ó tùún rí mi lómọ̀ọ́dún' o,
Igìngan ìgbò ni mo dà.
Ẹ r'òwo kìdùn mi' ni,
Ẹ ó sì tún r'àwo lọ́yọ̀nà o;
Igìngan ìgbò lawá dà.
Awo ni mi lóòtọ́ o,
Igìngan ìgbò ni mo dà.
Ikú wá mi délẹ̀,
Kò bá mi;
Igìngan ìgbò ni mo dà.
Àrùn wá mi délẹ̀,
Kò bá mi;
Igìngan ìgbò ni mo dà.
Òfò wá mi délẹ̀,
Kò bá mi;
Igìngan ìgbò ni mo dà.

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Ó yẹ̀ pọ̀ọ̀,
Ó họ̀ pọ̀rọ̀;
A dìà fún ọ̀yẹ̀lẹ̀ ìkòkò
Tí wọn ń pè láilẹ,
Tí ń bìmọ ọ̀ lẹ́lẹ̀gbẹ̀bì.
Ewé ọlọ́yọ̀ọ̀yọ̀ kì í jẹ́ ọràkọ mìlràn lẹ́ ayùnrẹ́.
Yìrẹ̀ ni í ṣe talọ,
Ẹ̀bọ̀ ni í ṣe tàkọ.
Yọlí ọ̀yẹ̀ o wàà bọ̀,
Ọmọ tuntun lèrè ọ̀yẹ̀bọ̀.
Àyẹ̀bọ̀ a dọmọ.
B'ọ́kan ò yẹ̀,
Ọ̀kan ò hù rí bí,
Láìlàn láìlàn n l'à ó hàlẹ̀ ọyìn.

## Ẹsẹ Ẹkaàrùn

Baba yẹkúyẹkú
Ni wọ́n ń pè l'Ọ̀yẹ̀kú;
Baba yẹ̀gẹ̀yẹ̀gẹ̀
Ni wọ́n ń pè l'Ọ̀yẹ̀.
Àrọ, wọn ò ṣe é gbà kọ̀ọ̀;
Àràrà ọ̀rìṣà, wọn ò ṣe é kí mọ́lẹ̀.
Mo rìn ọ̀nà tìtì,
Mo dé ìlú Òsoorogiro.
Mo mọ̀ mọ̀ d'ọmọ ọ̀pẹ̀ yẹ̀kẹ̀tẹ̀,
Kẹ́nìkẹ́ni mọ̀ mọ̀ ṣe nà mí o.
Ẹni t'ó bá nà mí,
A r'ìjà babaà mi.
Àrọmọ ọ̀pẹ̀ yẹ̀kẹ̀tẹ̀
Ni mo dà.
Ẹni ò n'Ọ̀yẹ̀kẹ̀,
A r'ìjà Ogbè.
Ẹ yà kìnà,
Ẹ jọ ng lọ.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Wọ́n rán mi l'ode Ọ̀pàràǹkìsà,
Mo bá wọn l'ode Ọ̀pàràǹkìsà.
Wọ́n rán mi l'ode Ọ̀pàràǹkìsà,
Mo bá wọn l'ode Ọ̀pàràǹkìsà.
Mo bá wọn,
Wọ́n ń f'igbá ahun dé ahun;
Wọ́n ń fi ìpẹ́ òòrẹ̀ dé òòrẹ̀;
Mo bá òòrẹ̀,
Nìbì tí wọ́n gbé ń f'ìpẹ́ dìpẹ́.
Bí ọ̀kàn bá jọ tán,*
Gbogbo ewéko ni í bá wọn yọ̀n ẹsẹ̀ ọ̀rìṣà.
Àgbàdìdìọ̀mọ̀ràn kì í bá wọn yùnrẹ̀ òòṣà.
Àgbàdìdìọ̀mọ̀ràn ọmọ Ọ̀yẹ̀kú,
Àgbà àyé, lẹ́ọ̀hànlun ọ̀rìṣà,
Kì í tọ̀run kò wá s'ílè ayé.
T'ilé ayé kì í bá wọ́n r'òde ọ̀run.
Àgbàdìrìn ni mo mọ̀ mọ̀ dà;
Kí ng mọ̀ mọ̀ bá wọn kòkò ìjọ̀bà o,
Àgbàdìdìọ̀mọ̀ràn ni mo mọ̀ mọ̀ dà.

## Ẹsẹ Ẹkeje

Ọ̀yẹ̀kú yakà,
Àwọn ọ̀rìṣà gbogbo ń sáà kiri;
A dìà fún Ọ̀yẹ̀kú
Tí yóò lọ rèé ya òkú ní Pọ́pọ̀.
Nígbàà lẹ́kẹ̀lẹ́ rí,
Bí òòyìn bá kú
Ní ìlú tí wọ́n ń pè ní Pọ́pọ̀,
Wọn kì í gbé wọ́n sin.
Wọn a ni bọ̀wá òkú lé tún jẹ́,
Wọn a dapọ̀ bò wọ́n.
Wọn a sì máa wò wọ́n lọ̀ọ̀,
Ṣùgbọ́n nígbà tí Ọ̀yẹ̀kú paara dé ìlú
Tí wọn ń pè ní Pọ́pọ̀ yìí,
Ó bá àwọn òkú tútù òtí gbìgbẹ,
Wọ́n pọ̀ lọ sun.

Ọ̀yẹ̀kú wáá sọ fún wọn pé
Òun ó jáde fún wọn ní ilú náà
Àfi bí wọn bá lè ya àwọn ẹ̀kúu wọn.
Wọ́n ní àwọn bẹ Ọ̀yẹ̀kú
Kí ó bá àwọn ya àwọn ẹ̀kú náà.
Ọ̀yẹ̀kú rúbọ, ó pe igún.
Ọ̀yẹ̀kú wọ̀yẹ̀, ó pe àkàlà.
Ọ̀yẹ̀kú rúbọ, ó pe tẹ̀ntẹ̀rẹ̀.
Gbogbo àwọn ẹyẹ wọ̀nyí
Ló ó jẹ àwọn ẹ̀kú náà.
Ọ̀yẹ̀kú wáá lọ sí ìgbó ìkẹ̀ Pópó,
Ó ní gbogbo ẹ̀kú t'ó bá tún kù,
Kí wọn ó máa gbé wọn wá,
Kí òun ó máa yà wọ́n.
Kùrò láru àwọn aráyé.
Bí wọn bá ti gbé wọn dé,
Ọ̀yẹ̀kú a ní kí wọn
Ó máa pàsán mẹ́jọ wá.
Ó ní pàsán náà ni òun
Ó fi ya àwọn ẹ̀kú náà.
Yóò sì fi pàsán náà kìlọ̀kọ̀ọ̀kan pé,
'A yà ọ́ lẹ́yẹ́,
A yà ọ́ nígun,
A yà ọ́ sí bodè ọ̀nà.'
Lẹ́hìn náà Ọ̀yẹ̀kú a ní
Kí wọn ó máa lọ
Ó ní àwọn ẹ̀kú náà
Kò gbọdọ̀ tún padà wá sáyé mọ́.
Báyìí ni àwọn aráyé ṣe sọ
Ọ̀yẹ̀kú di Ọ̀yàkú.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Olóòótọ́ tí ó bẹ láyé ò pògùn;
Ṣìkàṣìkà ìbẹ̀ wọn ò mọ níwọ̀n ẹgbẹ̀fà;
Ojú ìṣan ò lọ títí,
Kò jẹ́ kọ́ràn dun ni.
A dá fún ọ̀ràn gbogbo tí ó dun akápò
Bẹ́ẹ̀ ni wọn ò dun 'Fá.
Ọ̀ràn owó ń dun akápò;
Ọ̀ràn obìnrin ń dun akápò;
Ọ̀ràn ọmọ-bíbí ń dun akápò.
Akápò wáá lọ sọ fún Ọ̀rúnmìlà.
Ó ní gbogbo ire gbogbo ni òun ń wá.
Ọ̀rúnmìlà ní kí akápò ó lọ sọ fún Èṣù.
Èṣù ni gbogbo ọ̀ràn tí ń dun ìwọ akápò yí
Kò dun Ifá.
Èṣù ní ìwọ akápò,
Orí rẹ ni kí o lọ rò fún.
Nígbà tí akápò ṣe bẹ́ẹ̀ tán,
Ọ̀ràn rẹ̀ wáá bẹ̀rẹ̀ sí í dára.
Ijó ni akápò ń jó,
Ayọ̀ ni ó ń yọ̀;
Ó ń yin àwọn awo rẹ̀,
Àwọn awo rẹ̀ ń yin Ifá.
Ó ní bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́
Ni àwọn awo òun wí.
'Olóòótọ́ tí ó bẹ láyé ò pògùn;
Ṣìkàṣìkà ìbẹ̀ wọn ò mọ níwọ̀n ẹgbẹ̀fà;
Ojú ìṣan ò lọ títí,
Kò jẹ́ kọ́ràn dun ni;
A dá fún ọ̀ràn gbogbo tí ó dun akápò
Bẹ́ẹ̀ ni wọn ò dun Ifá.
Njẹ́, ohun gbogbo t'ó bá ń dùn mí,
Ng ó máa rò f'Órí mi.
Orí, mo kà mí o,
Ìwọ kìlàgbọ̀ràndùn.'

## ATÙMỌ̀

1 *Oyẹ́kú*: Awọ̀ ohù pẹ̀lẹ̀bẹ̀ kan báyìí tí kò nígé dàgbà, awọ̀ lẹ́lẹ́lẹ́ náà a máa fìnfìn rìnrìnrìnnin, wọn kì í sì í jẹ ẹ́.
2 *Olújìn*: orúkọ oyè ọba. Ilú l'ayé àtijọ́, Olófintuà ni Olújìn ìkókọ.
3 *Lákọ̀ọ́kọ́ọ́*: ní àtètèkọ́ṣe; ní ọdún tí ó kọjá.
4 *Bí ọdún bá ti dé*: bí ọdún bá padé tán.
5 *T'ìwọ ẹ̀ṣọ̀ lọ̀*: lọ sí òde ìṣan.
6 *akápò*: babaláwo tí ó kọ́ àpò Ifá.

# 3 ÌWÒRÌ MÉJÌ

### Ẹsẹ Èkíní

Ewọ̀ ọmí kò jọ ẹ̀wọ̀ ìrókò;
A dífá fún Àdàn
Tí yóò máa lọ rèé jí ọmí ẹlẹ́gẹ̀ ká jẹ.
Àdàn a máa jẹ èso kíri,
Ṣugbọ́n ẹ̀wọ̀ ìrókò l'ó fẹ́rán jù.
Àdàn wáá rí ẹ̀wọ̀ igi ọmí,
Ó sì fẹ́ẹ́ lọ jẹ é.
L'ó bá kọrí sí ilé babaláwo.
Ìwòrì Méjì ni Odù tí ó yọ sí i
Ní ọjọ́ náà.
Wọ́n ní kí Àdàn ó má ṣe dé ìbi ẹ̀wọ̀ ọmí
Ní ọ̀sán gangan o;
Wọ́n ní lóru ni kí ó máa jẹ ẹ́.
Wọ́n ní bí ó bá dé ìbi ẹ̀wọ̀ ọmí
Ní ọ̀sán gangan,
Wọ́n ní ẹlẹ́gẹ̀ ó fi kànnàkànnà pa á o.
Wọ́n ní, 'Ẹ̀wọ̀ ọmí
Tí àwọn ọmọ aráyé ń jẹ,
Kò jọ ẹ̀wọ̀ ìrókò
Tí àwọn ọmọ aráyé kì í jẹ.'
Àdàn ò gbọ́.
L'ó bá gbéra ní ọ̀sán gangan,
Ó lọ jẹ ẹ̀wọ̀ ọmí.
Nígbà tí ẹlẹ́gẹ̀ rí i,
Ó sì fi kànnàkànnà pa á.

### Ẹsẹ Èkejì

Ọwọ́ òwe ò tó pẹpẹ;
Tí ìgbálagbà ò wọ akèrègbè;
Ìgẹ̀ òwò bẹ ìgbà
Kò ó má ṣe kọ̀ mọ́;



Gbogbo wa ni a nígẹ̀ a jọ ó bẹ 'raa wa;
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà,
Ẹyí tí akápò rẹ̀
Ó pè lẹ́jọ́ l'ọ́dọ̀ Olódùmarè.
Olódùmarè wáá ránṣẹ́ sí Ọ̀rúnmìlà
Pé kí ó wáá sọ idí náà
Tí kò fi gba akápò rẹ̀.
Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà dé iwájú Olódùmarè,
Ó ní òun ń gbogbo agbára òun fún akápò,
Ó ní ìpín akápò ni kò gbọ́.
Nígbà náà ni òrọ̀ náà
Tó wáá yé Olódùmarè yékéyéké;
Inúu rẹ̀ sì dùn wí pé
Òun kò dá ẹjọ́ eékún kan.
Ní Ọlọ́dùá bá ní látí ọjọ́ náà lọ,
Ọmọ ẹdá kan kò gbọdọ̀ dá ẹjọ́ eékún kan.
Anikàndájọ́, o ò ṣeun;
Anikàndájọ́, o ò ṣèéyàn;
Nígbà tí o ò gbọ́ tẹnu ẹnìkejì,
Báwo l'o dájọ́ ṣe?

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ọrọ̀ ki i gba àrọ̀,
Kí á fi alọ́ sọ ọ́;
A dífá fún Òkòkó nìyẹ́lẹ̀
Tí yóò bá ni tòlẹ̀ yí wò,
Nígbà tí Olódùmarè kọ̀ ṣe ẹdá ènìyàn s'íle ayé,
Wọn ò rí ibi gbé
Nítorí pé ògédé omi ni gbogbo ilẹ̀ ayé.
Ní Ọ̀rúnmìlà bá lọ sí ọ̀dọ̀ Olódùmarè.
Olódùmarè wáá fún Ọ̀rúnmìlà
Ní ẹyẹlẹ́ mẹ́rin àti àkùkọ adìẹ kan.
Àwọn ni wọ́n tan ẹ̀rùpẹ̀ inú agbọ̀n,
Tí Olódùmarè sọ kalẹ̀ láti òde ọ̀run.
Ní gbogbo ayé ń di ìgbàtẹ́jú báyìí.
Ìjó ni àwọn ọmọ aráyé ń jó,
Ayọ̀ ni wọ́n ń yọ̀;
Wọ́n ń yin Ìwòrì Méjì,
Ìwòrì Méjì ń yin Ifá.

Wọn ni, 'Kin ni ó báà ni tùnlẹ̀ yí so?
Okùko niyẹ̀lẹ̀
Ni yóò wáá bá ni tùnlẹ̀ yí ṣe.'

## Ẹsẹ Èkẹrin

Ara ilú ẹ̀ẹ̀dọ̀,
Mo dá lójú,
Mo fi dé ọmú;
Mo ṣe àgbọn inàlẹ̀ warí warí;
A dìá fún Ogún,
Onìjà-mọle,
Ní ọjọ́ tí ó lọ sí oko ọdẹ.
Wọn ní kí ó kàalẹ̀,
Ẹbọ ni kí ó ṣe.
Wọn ní kí ó rú ẹṣẹ dìdìdí kan,
Ilujé dìẹ̀, ìpẹ̀pẹ́ irin, mọ́rìnwó ọ̀pẹ̀,
Àti ewé ilá ìrúdò.
Gbogbo rẹ̀ nàà ni Ogún rú.
Àwọn awon rẹ̀ẹ̀ wá ni kó gbé ẹbọ nàà
Lọ sí ìdiì oko
Nibi tí àwọn àgbọ̀nrín gbé ń jẹ.
Ngbà tí ó débẹ̀,
Ó pa ìbàrun gidi kan.
Ó ní, 'Kín ni onìbùjé pa?
Ẹ ó wa ekinín àti ataàn.'
Kín ni onìbùjé pa?
Ẹ wo ekinín àti atìm.'

## Ẹsẹ Èkarùn

Lòòrọ̀ kíìrìrí ni ọmọ kékeré ń yaniin ragbé;
Ilíkàn l'ó kọ̀'lée tiẹ̀;
Ilẹ̀ẹ̀ ni kò fi f'omi ṣe;
Àfèbọ̀jọ̀ ni í walẹ̀ẹ̀ tiẹ̀ ni wònùkoro wònùkoro.
Ilé afèbọ̀jọ̀ gbayè, ó ghùné,
Ilẹ̀ẹ̀ ni kò gbọdọ̀ jọba;
Ilou kékeré ni i kọ̀'lée tiẹ̀,
A ṣọ kòbà ikòlò;
Ẹgà ni í kọ̀'lée tiẹ̀,



Wọn a dari kodò bèbèrùdò;
Ọkàn ṣoṣo Èjì Ìwòrì
L'ó lọ igbó ọlà sílẹ̀;
Àwon wọn n'Ilé Ọlọ́fin;
Ègàn tí mo gùn, kò gbélẹ̀ẹ̀;
Èpìtí mi, kò ṣàjà.
A dìá fún Kékeré Ọdẹ
Àti Ọ̀fìnràn Ọ̀kẹ́jà.
Wọn ń lọ rèé dẹ̀'gbó Ìwòrì
Ní ọ̀dún gangan.
Wọn ní kí wọn ó mọ̀ lọ dẹ igbó nàà
Àfi bí wọn bá rúbọ dàadàa.
Ṣùgbọ́n Ọ̀fìnràn Ọ̀kẹ́jà kò gbọ́.
L'ó bá mára ní ọ̀dún gangan,
Ó sì wọ'nú igbó Ìwòrì.
Bí ó ti wọ'nú igbó nàà,
Ni àwọn iwin bá da kijìpá mámu bò ó lórí.
A ó tí ṣe mọ̀ Ọ̀fìnràn ọ̀kẹ́jà
Ni à ó pè ní ọ̀kún
Kíjìpá ẹbọ Ìwòrì tí kò rú nàà
Ni ọ̀kún ó gbé kiri di òní.

## Ẹsẹ Èkẹfà

Ẹ̀là torofíni torofíni,
Ẹ̀là torofíni torofíni;
Ẹ̀là tòòmolẹ̀,
Ẹ̀là pọndéwòrè;
Agbe màá gbókùn mi rèkun;
Àlùkò màá gbóhùn mi rọ̀sà;
Ọ̀kànkìlògùn òrìṣà;
A dìá fún Ọ̀kínkí
Tí wọn ó fi lédà nyè ilée babaa rẹ̀.
Wọn ní ìre ajé ó tó o kéré.
Wọn ní ìre ọmọ ó tó o lọ́wọ́.
Há, h'ó o bá jẹ̀ k'ìre ajé ó tó mi lọ́wọ́,
Àtẹ̀wọ́ọ̀ mi ẹ̀wà,
Àtẹ̀wọ́ọ̀ mi ẹ̀wà;
Àpárá ni ṣìkọkànkìlògùn
Há, bun mí ng ó màá sin ọ̀ ni Mòkun,

N'Ìlé ọri;
Ní Mọ̀ṣà Ọ̀tùn,
N'Ìlé Elẹ́jẹ̀lú,
Ọmọ erin tí í fọn kíkan;
Ọbàtálá ìgẹ́rin ìjà Àkó,
Ọ̀rúnmìlà jẹ́ kí ng rù ọ́ tù,
Jẹ́ kí ng rù ọ́ gbó.

## Ẹsẹ̀ Èkejì

Ìwòrì wòrì wòrì;
A dìá fún alágbẹ̀dẹ Ìmògún,
Tí ó maa f'irin jọnà
Nítorí pé ó ń wẹjú,
Nítorí pé ó ń wẹmu;
Tí kò sí lè kojú mọ̀ṣẹ́ tí ó ṣe.
Nígbà láíláí, bí alágbẹ̀dẹ̀ ba ti kí irin bọnà,
Bí ọwọ́ọ wọn bá ti rírí,
Wọn a fi ọmọ̀ họnà.
Wọn a fọ̀ ọ̀ rò.
Ṣùgbọ́n nígbà tí wọn bá ń ṣe èyí,
Irin á ti jónà bàjẹ́,
Kò sì ní í dára mọ́
Fún olùun tí wọ́n fẹ́ẹ̀ ṣe.
Alágbẹ̀dẹ Ìmògún wáá mú oókan pẹ̀lú ọ̀ọ̀jí,
Ó lọrí s'ọ́dọ̀ Ìwòrì.
Látì lọ bèèrè ohun tí òún lè ṣe.
Ìwòrì ní kò sí ohun tí yóò ṣe
Ju pé kí ó máa fi ọmọ̀ bọ́jú ìrì ọmọ
Lẹ́hìn ìgbà tí ó bá parí iṣẹ́ẹ rẹ̀ lóòjọ́,
Kí ó wáá lọ wẹ̀.
Alágbẹ̀dẹ Ìmògún sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Iṣẹ́ẹ rẹ̀ sì dára.
Nígbà tí wọ́n bi í pé
Nílou l'ó ti rí òògùn rẹ̀ ṣe
Tí irin rẹ̀ kò fi jónà mọ́?
Alágbẹ̀dẹ Ìmògún ní,
'Bí ó sí Ìwòrì,
T'ó ní kí n dá lọ́jú;
Kí n dá lẹ́nu;
Kí n ṣe ìgbọ́n bàlẹ̀ wòrì wòrì;
Gbogbo irin ìbá ti jónà tán.'

## Ẹsẹ̀ Èkẹta

Òdè kùn, òde kò kùn tìtì;
Ìmọ̀ òdè lọ, kò lọ jìnà;
A dìá fún Ìwòrì,
Tí ó lọ rèé ṣe òde n'Ífẹ̀.
Wọ́n ní ẹbọọ kí ó lọ tìtì
Ni kí ó ṣe.
Òdè gbọ́, òde kò ní.
Ọmọọ rẹ̀ẹ́ lọ tán,
Ọmọọ rẹ̀ ń túkáá lọ.
Òdè kùn tìtì,
Òdè dì alẹ̀,
Ọ̀gànjọ́ gàn,
Òdè rò lánùn.
Àwọn Olódè-n-mọ̀-kò-òde
Wáá jò sàárin òde,
Wọ́n kígbe hìì tìtìo;
Wọ́n ní, 'Àbjìn jìn, ẹ máa túkáá lọ.'
Ni gbogbo ọmọ òdè bá túkà lọ.
Àṣẹ sìrà ẹbọ ní í gbe ni.
Àìrà kì í gbèèyàn;
Kóè pọ̀ o, kóè jìnà,
Ẹ máa wo'fá awo kí,
B'ó tí ń ṣe.

## ÀTÙMỌ̀

1 *Ẹsọ*: òro ìgi tí ó wà nílẹ̀.
2 *Ẹwù*: igi kan tí ó bọ ní ọ̀dàn.
3 *Ìbàwuu gàlà*: ìgbẹ̀sẹrìn alà.
4 *Ẹ̀hìnù*: Ìwo ọ̀dà.
5 *Àbàù*: àtíbàbà tí awọn ọdẹ máa ń yan ẹran ní orí rẹ̀.

# 4 ÒDÍ MÉJÌ

## Ese Ẹ̀kíní

Ilé ni mo jókòó sí,
Ni gbogbo ire ń wọ́ tuurutu wáà bá mi;
Òde ilé ni mo jókòó kà,
Gbogbo ọrọ̀ ń wọ́ tuurutu wáà bá mi;
Mo jókòó kinàrò,
Mo r'ire ọrọ̀ t'ó pọ̀ repete.
A díà fún Òdì
Tí ń gasasi lọ sí òde Òkò.
Ó jókòó l'ẹ́yin t'ìgì akòko.
Ire gbogbo ń dà wá o,
Igiriri, igiriri
Ibi a l'íyọ̀ sí ni iyọ̀ọ́ ṣomí sí;
Ire gbogbo dà wá o,
Igiriri igiriri.
Òkè ki iyọ̀ ti í fi í gb'ọbọọ tiè;
Ire gbogbo dà wá o,
Igiriri, igiriri.

## Ese Ẹ̀kejì

Òdì ki í jẹ òdì,
Awon wọn n'Ilé Kètu;
A díà fún iyá tí ń ṣẹ̀ṣẹ́ àrọ̀sin
Tí à ń pè ní Àdì,
Tí Ọbalúayé[1] ó gbọdọ̀ jẹ.
Ẹkùrọ̀ ki í tí í ṣe àrọ̀sin rẹ̀;
Òdì l'ó ṣe ológun fún iyá tí à ń pè ní Àdì
Tí ó wo Ẹ̀pà dàgbà,
Kí ẹkùrọ̀ ó tóó lè máa ṣe àrọ̀sin
Tí à ń pè ní Àdì.
Nítorí pé àwọn ẹ̀yan á pe àrọ̀sin ní Àdì,



Tí í ṣe oriki iyá Ẹ̀pà
Ní Ẹ̀pà kò fi gbọdọ̀ jẹ àdì rírí.
Àdì ni iyá Ẹ̀pàà jẹ́,
Ẹ̀ má fi àdì rúbọ l'Ọ̀balúayé.

## Ese Ẹ̀kẹta

Òdì Méjèèjì, awo ilé Alárá;
Òdì Méjèèjì, awo ilé Ọlọ́fin;
Òdì Méjèèjì, awon wọn níkì Ọwáringún-àgà,
Àmọ̀tìdí, ọmọ omọ̀gì,
Àgùn l'ọwọ́ lílà ajé tètèrè.[2]
Wọ́n ní iwọ Òdì Méjì,
Ó ti wáà jẹ́ o?
Tí ahọ́gún ilé kò fi bá ùbàrin;
Tí àgùn kò t'ọmọ́ àlà bùsùn?
Òdì ní ẹbọ ni kí wọn ó rú.
Wọ́n rúbọ tán,
Wọ́n ṣefá fún wọn.
Wọ́n ní t'ire ajé, ire ọmọ,
Ire àìkú pari ìwà.
Wọ́n ní n l'a b'Ẹ̀pà o ò,
Kangiri,
Àìkú l'a b'Ẹ̀pà o ò,
Kangiri.

## Ese Ẹ̀kẹrin

Òdì àgbálagbà Ifẹ̀,
Awo ilé Ọlọ́fin;
A díà fún Ọlọ́fin
Tí ó pàrakò[3] ránṣẹ́ sí Àjàkà.[4]
Nígbà tí àwọn mú Ifẹ̀
Kò fẹ́ẹ́ mú ìsìngbà[5] lọ sí Ọ̀yọ́ mọ́,
Wọ́n wáá lọ bá Òdì
Pé kí ó gba àwọn ní ìmọ̀rán.
Òdì ni kí wọn ó rú ìdin àgbọn mẹ́rindinlógún
Ati igbá ẹrù igi kan.
Kí wọn ó pésè sí i lára,

Kí wọn ó wáá gbé a rámúṣẹ́ sí Ọ̀yọ́,
Kí wọn ó sọ fún Aláàfin pé
Ilá ọ̀dún náà ti yọ̀ dáá,
Agbọn-ìdu ni kí ó fi ṣe ìkin.
Àti wí pé ọmọ̀ọ̀ rẹ̀ obìnrin ti ó bímọ,
Kí ó má fi ẹrù ìgì náà yàná.
Nígbà tí Aláàfin ri èyí,
Ó pe Ọ̀sà pé kí ó wáá túmọ̀
Àrokò tí Ọlọ́fin pa rámúṣẹ́ sí òun.
Ọ̀sá wáá wí fún Àjàkà pé
Àwọn ará Ifẹ̀ kò fẹ́ẹ́ sin ìsìngbà mọ́;
Àti wí pé agbálagba ọmọ kan
Ń bẹ ní ẹgbẹ́ẹ̀ wọn.
Látì ọjọ́ náà ni Àjàkà ó ti yọ
Àwọn ará Ifẹ̀ lọ́rùn mọ́ fún ìsìngbà.
Ìjó ni àwọn ará Ifẹ̀ ń jó,
Ayọ̀ ni wọ́n ń yọ̀,
Wọn ní, 'Odì o,
Àgbàlagbà Ifẹ̀.
Odì o,
Àgbàlagbà Ifẹ̀.'



## Ẹsẹ Ẹ̀kaàrùn

Àpá ewúrẹ́ ni kì í jẹ́ kí à pa ewúrẹ́;
A dá fún Jàkúta,
Tí í ṣe àrẹ̀mọ Ṣàngó.
Ǹjẹ́, òní l'a ó pa Jàkúta;
Ọ̀la l'a ó pa Jàkúta;
Ọ̀tunla l'a ó pa Jàkúta;
Ìrènì? l'a ó pa Jàkúta;
Ọ̀rún? l'a ó pa Jàkúta;
Ẹ̀rù, ẹ̀rù, l'a ó fi pa Jàkúta mọ́.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Kí-à dí ìlẹ̀ kò kún bámúbámú;
A dá fún ataare
Tí kì í di ẹrùn tiẹ̀
Láìkún ọmọ.
Ǹjẹ́ ìgba orógbó,
Ìgba ataare,
Ìgba ẹyọ̀ọ̀ rẹ̀rẹ̀,
Ìgba ọ̀kàa bàbà;
Tà l'ó pé Odù ó lówó lọ́wọ́?
Àyàmọ̀ bí ẹ̀ẹ̀rẹ̀
Kí i báá ṣe gbọ́jẹ̀ Ṣàngó.
Ifá dá, aláṣẹ,
Ẹ̀bọra abìṣe,
Ọ̀pẹ̀, abìṣẹ wàrà.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ó tàpá lókun;
Ó tàkìtì lọ́sà;
Akùn l'ó gbé'nú odò
L'ó ń ṣèbọ aarunuru l'Ọ́lọ́fin;
A dá fún Ọ̀rúnmìlà,
Ifá ó mu bàbà,
Ìlẹ̀ẹ̀ ni kò mu ọ̀kẹ̀tẹ̀,
Ifá ó niyè ònà mọ́.
Ọba aládé gbogbo ọ̀ní kan,
Iyà Ẹdú là wàà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Ọ̀rán t'ó bá ó dun bolobòwo
Ní í dun Ifá;
Ọ̀rán t'ó bá ó dun onlẹ́gùn
Wọn a dun Ọ̀sanyìn;
Ọ̀rán t'ó bá á d'ajẹ́
Ní í dun obìnrin ìsọ ilé ẹ;
A dá fún Ọ̀rúnmìlà,
Ọmọ onídẹ̀kọ̀ọ̀;
Yóò gbẹ́lẹ̀wá,
Yóò sì gbàpèrẹ̀ ọmọ ọ̀bọ̀ gaya.
Ẹrù Ìpọ̀,
Ẹrù Ọ̀fà,
Ẹ wáà bá mi ní àrìrọ̀gùn;
Àrìrọ̀gùn l'àwá wà.

## ÀTÙMỌ̀

1 *Ọ̀balùayé*: orukọ Èṣù.
2 *Àgùn f'ọwọ́ lábẹ́ ajé kókóró*: Ẹni ti ó gùn dàadàa ti ó fi jẹ́ ní pé ó gùn ju ... Àbí ... ti wọn ... ọ̀pọ̀ ní.
3 *Pẹ̀rẹ̀bè*: Ìi olusi ... kan ... ní ... ti ó fi olusi ... ni.
4 *Àjàbò*: ọ̀kan nínú awọn Àláàfin Ọ̀yọ́ tí ó jẹ ní Ọ̀yọ́-Ilé.
5 *Àsògbò*: olusi ti ìwọn ... ti ó wà lọ́dọ̀ Àláàfin ... Àsògbò yìí ló fi ... wà lọ́dọ̀ Àláàfin.
6 *Ìrèsì*: ọjọ́ mẹ́rin ìsìn.
7 *Ọ̀rún*: ọjọ́ mararùn ìsìn.



# 5 ÌROSÙN MÉJÌ

### Ẹsẹ Èkínní

Àṣẹ ṣẹ́ wá,
Ẹ̀ṣọ̀ ṣẹ́ wá;
A diá fún Iyá ọlọ́mọ,
Àbìrí àti ìkókó
Tí wọn ń lọ s'ílẹ̀ Ilakú.
Wọn dé'nú ayé,
Wọn tẹ̀ bodè sílẹ̀,
Àṣẹ̀yìnwá, àṣẹ̀yìnbọ̀,
Ọ̀tẹ̀ tẹ̀ ọbàbodè, a dọmọ.

### Ẹsẹ Èkejì

Bí ọmọdé bá jí,
Wọn a fi àrán bàbáa wọn lọ́rùn,
Wọn a ṣọwọ́ fìnrìngìngìn fìnrìngìngìn;
Bí ọmọdé bá jí,
Wọn a gbé àrán bàbáa wọn,
Wọn a ṣọwọ́ fìnrìngìngìn fìnrìngìngìn;
A diá fún Yèwọ̀pa[1]
Tí wọn ṣefá fún ní Ìrẹ̀sì Orò.[2]
À ní o yàwọ́ pabì,[3]
O ti ṣe yàwọ́ pẹ̀rẹ̀n.
Yèwọ̀pa, ọmọọ wọn Ìrẹ̀sì Orò.
À ní o yàwọ́ pabì,
O ti ṣe yàwọ́ pẹ̀rẹ̀n.
Yèwọ̀pa, ọmọọ wọn Ìrẹ̀sì Orò.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Àkùnọ̀, a ti ṣe ẹ́;
A ṣekú tan,
Ilú àwùwo,

A dúà fún Èkòsè ilè
Tí ó fi ògbó jayé.
Wọn ní ó kàrálẹ̀,
Ó jàre,
Ẹbọ ni kí ó ṣe,
Ó pawo likòó;
Ó pilàn idé;
Ó wọrun yàn yààn yàn
Bí ọni tí ó ní í kú mọ́ láyé,
Ó wàá lọ'tí ọgbọ̀n ẹ̀bọ.
Kéè pẹ́ o,
Kéè jìnà,
Ẹ wáá wofa awo kí
B'ó tí ń ṣe,
Ha ẹ̀, ahìṣẹ,
Ọ̀pẹ̀, ahìṣẹ wàrà.

## Ese Ẹ̀kẹrin

Eti ṣeere ni i mú wọ́n wọgbó;
Ọ̀rúgbòndà ọṣàn, wọn a wọ̀ sijà;
Ẹni bubuni wọgbó,
Ìwàn rẹ̀ a tọ̀ ó;
A dúà fún Ọ̀rúnmìlà,
Baba ń lọ rèé ra Taraẹnilàágbó lẹ́rú.
Àwáàgbọ́, àfiẹ̀àgbó.
Wọn kilọ̀ fún Taraẹnikọ́n,
Wọn ò gbọ́.
Wọ́n tún kọ́ti ọ̀gbọ̀n ẹ̀bọ.
Àsẹ̀hinwá, àsẹ̀hinbọ̀,
Taraẹnilọ́ùn wọ̀gbé,
Wọn ń ṣe bí ajàkoó kiri.
Àfàiyọ̀, k'ó tóó mọ̀ jẹ̀ẹ́ pé Taraẹnilọ́jà ni lùàki.
Àfàimọ̀, k'ó tóó mọ̀ jẹ̀ẹ́ pé Taraẹnilọ́jà ni ọ̀bọ.

## Ese Ẹ̀kaárùn

Àbùkọ̀ l'ogbe lẹ̀bẹ̀lẹ̀bẹ̀ ṣeyè;
A dúà fún Òpìlìkì
Tí ó fi tiẹ̀ silẹ̀,



Tí ó mọn gbò ti ṣiùẹ̀lọni kàyé kiri,
Ọ̀rúnmìlà ní ó ó bá a tún ilẹ̀ wá ṣe.
Wọ́n ní kí Òpìlìkì ó rúbọ,
Kí ó lè bọ̀ ayé láyé.
Ó sì rú u.
Ìgbà t'ó rúbọ tán,
Wọ́n ní kí ó máa tún ti ṣaaṣẹ ẹlomirán ṣe
Jù bí ó ti ń tún ti araa rẹ̀ ṣe lọ.
Ìgbà tí ó ṣe gbogbo ẹ̀ tán,
Tí ó mọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ omiàrè tán,
Orin awo ní ó ń kọ,
Ó ní kín ní ó bàá mi tùnmọ̀a tiemi ṣe?
Ọ̀rúnmìlà, àbá mi, Ẹ̀rìgì Àlọ,
Ní yóò bá mi tùnmọ̀a tèmi ṣe.

## Ese Ẹ̀kẹfà

Ó ṣeere làlọ,
Ó ni ṣeere làbọ̀;
Yinkin r'ó kú sí ó fi bájẹ́;
A dúà fún Ògún,
Onìjà-nilè,
Ẹ̀jẹmu Olúwọnran,
A dí ginìgiri ro'lé ìjà.
Níjọ́ tí ó lọ sógun Ìgbònnakò Ẹ̀sẹ̀ṣẹ̀,
Ogun Ìgbònnakò rí òun ó lọ yíí,
Òun rìṣe bọ̀ rúbọ;
Òun mú ṣe.
Òun mú tà bọ̀ ogun náà.
Wọ́n ní ẹbọ ni ki ó wáá rú.
Ó sì rú u.
Ìgbà ó rúbọ tán,
Ó sì ṣẹ́gun sí ìjàrin,
Ó ṣẹ́gun sí òsì,
Ó bí àmọn ọ̀nà bálẹ̀ lààrin.
Erú Ìpo,
Erú Ọ̀fà;
Ẹ wáá bá ni ní àrùṣẹ̀gun,
...ṣẹ̀ l'ààá rè.

## Ese Ìkeje

Ọkọ̀nkọ̀ara, a f'ọwọ́ tìkó;
Idà ṣe gbẹ̀rẹ́gbẹ̀rẹ́ wàkọ̀;
Bí erin ó wọdò,
A kìgbe bíi rọ́ọ̀n;
Bí àjàmà[6] ó wọdò,
A rìn ìkitìmọ̀, ìkitìmọ̀;
A dìà fún iyá Ìdèrè,[7]
'Tí ó lọ lùú kanrílẹ̀ ọmọ ní bíbí.[8]
Wọ́n ní ó kàakì Mọlẹ̀,
Ó jàre,
Ẹbọ ni kí ó ṣe.
Wọ́n ní kí ó rú ìgbín méjì,
K'ó rú pọ̀pọ̀kọ̀ owúu kan,
K'ó sì rú kànyinkànyin.
Ó gbọ́, kò rú.
Ó bìnụ tán,
Ojú ò pọ́n ọmọọ rẹ̀.
Rírú ẹbọ ní í gbe ni,
Àìrú kì í gbèèyàn.
Kèè pẹ́ o,
Kèè jìnà,
Ẹ wáá wo'fá awo kí
Ifá tí ó ṣẹ.
Ifá dé, aláṣẹ;
Ọ̀pẹ̀, aláṣẹ wàrà.

## Ese Ìkejọ

Bọọrọ l'ó yẹlẹ́;
Àtẹ̀rìghà a yẹ ọ̀dẹ̀dẹ̀;
Àkòdì kan gbàrùgbàdà l'ó yẹ mí,
Ní l'ó yọmọ̀n mí.
A dìà fún Fàtìkó[9]
I.Èupe,[10] n'ílé alétè wỌyn,[11]
Afọ̀dì ọkọ̀ ṭẹ̀lẹ̀ fọ mọ̀gàmọ̀gà.[12]
Nịẹ̀ ìdìì àwọ̀n lè yé ara àwọn bàyìí?
Ní àwọn ará Èupe dìfá sí.
Wọ́n ní kí wọn ó rúbọ.
Kín ni àwọn ó wa rú bàyìí?
Wọ́n ní kí wọn ó rú ewúrẹ́ ẹlẹ́ kan.
Kí wọn ó fi ewúrẹ́ náà bọ Ìbàmìlí wọn.
Kí wọn ó sì fi ilẹ̀ àjọni kan sílẹ̀,
Kí ẹnikẹ́ni ó má ṣe lò ó mọ́,
Nítorí pé ilẹ̀ náà ni ó dá èdè ìlàyedè sílẹ̀.
Nígbà tí wọ́n ṣe bẹ́ẹ̀ tán,
Tí ọ̀nàn wọ́n dayọ̀ tán,
Wọ́n wáá bẹ̀rẹ̀ sí í jó gìrìgan.
Onígìrìgan ń ví pé:
'Ọpẹ̀ ti fọ Tàpà,
Ẹ ò gbọ́ ni.
Èdè mọ̀ mọ̀ ti fọ Tàpà,
Ẹ ò gbọ́ ni.
Ọpẹ̀ ti fọ Tàpà,
Ẹ ò gbọ́ ni.'

## ATÚMỌ̀

1 *Ọ̀kọ̀nkọ̀ra*: orúkọ ìlú kan.
2 *Ìrẹ̀dì*: orúkọ ìlú kan.
3 *Ìbáà*: pa ọlá.
4 *Ọ̀nà ọ̀dà, ẹ̀gànn oòkọ̀rọ̀nìnì, a di gbòọ̀rì n'ílé ẹ̀jì*: orúkọ Ògún tí ìwọ̀nyí.
5 *Ìgbàmọ̀dì Èrìjẹ̀*: orúkọ ìlú kan.
6 *Àjàmà*: àjàmàlà; erin.
7 *Ìdèrè*: ìlú kan ní Ìbàràpá.
8 *Kanrílẹ̀ ọmọ ní bíbí*: bẹ̀rẹ̀ sí í bí ọmọkọ̀ọ ọmọ.
9 *Fàtìkó*: orúkọ ẹnìkan.
10 *I.Èupe*: ní Èupe. Èupe jẹ́ ìlú àwọn Tàpà.
11 *Wọ̀yọ*: wọ ọdọ̀ Ọ̀yọ́.
12 *Mọ̀gàmọ̀gà*: èdè àwọn Tàpà.

## 6 ỌWỌ̀NRÍN MẸ́JÌ

### Ẹsẹ Èkíní

Ọwọ̀n omi, ọ̀wọ̀n omi,
Ọwọ̀n àràkọ ti à á pe Ọ̀wọ̀nrín.
Ọwọ̀n ẹ̀jẹ̀ ni à á pè lẹ̀gbìn.
Akitipò, akitipò, akitipò;
Ọ̀wọ̀ sísì, ọ̀wọ̀ sísì.
Àwọ̀ọ̀dà òkunru, àwọ̀ọ̀dà òkunru, àwọ̀ọ̀dà òkunru.
Ọwààrà, ọ̀wọ̀ ṣìṣìṣì.
Ọwààrà, ọ̀wọ̀ ṣìṣìṣì.
Bí wọ́n bá ń rọ̀,
Wọn kì í dá rọ̀.
Ejì n yo àlọ̀;
Ejì n yo wàko;
Àbìnà rẹ̀gẹ̀dẹ̀ n sì dodò.
A dífá fún Ọ̀wọ̀-wìnìwìnì,
Tí í ṣ'ọmọ Olókun, ajìsí ailé.
Ọmọ a wọ̀ omi kunru gbà jọ;
Ọ̀wọ̀ ṣìṣì, ọ̀wọ̀ ṣìṣì.

### Ẹsẹ Èkejì

Aparun ṣẹ́gi l'òkè ìlún;
Aparun ṣẹ́gi l'òkè ọ̀lọ́n;
A dífá fún Ọ̀wọ̀n,
Tí ń sogun Tẹ̀ntẹ̀sìn.
Ogun tí òun ó lọ yìí,
Òun ló ja àjàjà nbẹ̀?
Ni Ọ̀wọ̀n dá Ifá sí.
Wọ́n ní yóò ṣẹ́gun,
Ṣùgbọ́n kí ó rúbọ.
Kín ni òun ó ha ní báyìí?
Wọ́n ní kí ó rú ẹwà ẹ̀rìn àtàa rẹ̀,
Kí ó sì rú ọgbààjọ owó.



Ó rúbọ tán,
Wọ́n ṣe Ifá fún un.
Ó sì ja ogun náà ní òjòjò,
Ó ja ogun náà ní òjòmọ́rọ̀.
Ó mú ọ̀kùnrin,
Ó sì mú obìnrin.
Ó ṣẹ́gun ní'wòjò,
Ó ṣẹ́gun nẹ́yìn,
Ó sì bí ọ̀tá lulẹ̀ láìrin.
Ó wáá ń yin àwọn awo rẹ̀,
Àwọn awo rẹ̀ ń yin Ifá.
Ó ní, 'Ta ní ó ò mú mẹ́jì o,
Ọ̀wọ̀n l'ó mú mẹ́jì o.'

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Àtẹ̀lẹwọ́ ò lèè hunrun ìhìrè ìhìrè;
Kò ṣe ẹ̀rẹ̀fẹ̀rẹ̀,
K'ó rí ẹ̀rẹ̀fẹ̀rẹ̀ bí alá;
A dífá fún Mọ́fẹ́ọ̀ní,
Tí ó lọ rèé kówó lọ́dọ̀ọ Kìífẹ́ọ̀ní.
Ojú ni ó pọ́n Mọ́fẹ́ọ̀ní,
L'ó bá lọ kówó lọ́dọ̀ọ Kìífẹ́ọ̀ní.
Wọ́n wáá ń wá ọ̀kà adìẹ
Tí ọ̀bọ ó fi ṣe ògùn
Kí ọmọọ rẹ̀ ban ṣẹ̀ṣẹ̀ ó lè yè.
Wọ́n wá òkùdẹ̀ náà títí, wọ́n ò rí
Tí wọ́n fi wá a dé oko Ọbàmàrìnmí,
Níbi tí Mọ́fẹ́ọ̀ní tí ń singbà' l'ọ́dọ̀ọ Kìífẹ́ọ̀ní.
Mọ́fẹ́ọ̀ní sì ní àkùkọ adìẹ kan,
Àkùkọ adìẹ náà sì kó sínú àgò.
Nígbà tí àwọn mìíràn-ọbà dé,
Wọ́n bi àkùkọ adìẹ náà.
Wọ́n bi Kìífẹ́ọ̀ní pé ta l'ó ni ín.
Kìífẹ́ọ̀ní ní òun kọ́ o.
Ó ní Ọlọ́run nìí jẹ́ kí òun ó dé.
Àkùkọ adìẹ t'ó ti kò mọ́'nú àgò ní tìnin.
Ó ṣe bí ọbà fẹ́ẹ̀ mú ẹni tí ó ni àkùkọ náà ni.
Ó ní lwọ́fà òun, olóríburúkú kan báyìí,
L'ó ni àkùkọ adìẹ náà.

Wàrì, ó ti rántíyẹ́ si Mọfẹ́ọ̀nì
Ní okon Gbàmìorìmí níbi t'ó gbé ń ṣiṣẹ́ àṣedìẹ́u,
Níbi t'ó gbé ń sìngbà, tí ń ṣèsìn.
Tí ń ṣiṣẹ́ bìn-jì-o-jìmì,
Tí Mọfẹ́ọ̀nì gbé ń ṣiṣẹ́ àṣedìàjìn.
Nígbà tí Mọfẹ́ọ̀nì dé,
Wọ́n bí í pé ṣé òun l'ó ni
Àkùkọ adìẹ t'ó kú s'ínú àgò náà.
Ó sì dáhùn pé òun ni.
Wọ́n ní àwọn fẹ́ rà á ni.
Kí Mọfẹ́ọ̀nì ó tóó yanu fọhùn,
Wọ́n ti fún un ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó,
Wọ́n ní owó àkùkọ adìẹ rẹ̀ rè-un,
Ni Mọfẹ́ọ̀nì bá di ọlọ́rọ̀, ó dalájé.
Ó yà ọmọ kótó,
Orin awo ní ń kọ.
Ó ní, 'Mo fẹ́,
Ng ò lówó o,
Iyẹ́rẹ̀.
Mo mọ̀ mọ̀ fẹ́,
Ng ò bímọ.
Iyẹ́rẹ̀.
Iyẹ́rẹ̀ ìtí l'a ó fi ùnì mọ,
Iyẹ́rẹ̀.'

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Wọ́nmọn, wọ́nwọn, ọ̀wọ́nràànwọ̀nràn;
A dífá fún Wọ́nranwọ̀nran Ọ̀wọ̀n.
Ìnú l'ó fi í ṣèlé,
Àtàrì l'ó fi í ṣe èbùrú ọ̀nà.
Ọ̀wọ̀nrànwọ̀nràn,
Tú ọmọ awo sílẹ̀,
K'ó r'íbi ṣe ayẹ́ rẹ̀ o.
Ẹ kì ìmá ọmọ Ifá,
Ẹ ó ní gbọ́nà mọ́ ọmọ Odù.
Ọmọ Ifá niyí o,
Ọmọ Odù ni í,
Ẹ tú u sílẹ̀.



Ẹ jẹ́ kí ó lọ.
Ẹ tú u sílẹ̀,
Ẹ jẹ́ kí ó lọ.

## Ẹsẹ Ẹkaarùn

Onílẹ̀kẹ̀ ìngún,
Àlàbọ̀jà ìngbọ̀n,
Onlkodaṣùkodo[1] ní Àlàfọ̀ta;
A dífá fún Ọlọ́mọ́bàkà,[2]
Tí í ṣe ọ̀rẹ́mọ Ọlọ́fin.
Wọ́n ní kí Ọlọ́mọ́bàkà ó rúbọ
Nítorí ikú.
Kín ni òun ó ha rú bọ́ọ̀?
Wọ́n ní ó rú àgbébọ̀ adìẹ kan,
K'ó sì rú àádọ́ọ̀ owó.
Ó rúbọ,
Wọ́n ṣe Ifá fún un.
Ikú àti àrùn kò sì lọ́ ṣe ó mọ́.
Ó ní àwúdì-gbé ikún ni rà lọ tàm tàm
Àwúdì gbé ikún mi rà lọ tàm réré.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ọ̀rúnmìlà ní ó ń dún yùnmuyùnmu,
Ó ń kùn yùnmuyùnmu
L'órí àpáta àgbàrànsala,
Wọ́n ní ta ni ń dún yùnmuyùnmu,
Tí ń kùn yùnmuyùnmu
L'órí àpáta àgbàrànsala?
Wọ́n ní ajé l'ó ń dún yùnmuyùnmu,
Ajé l'ó ń kùn yùnmuyùnmu,
L'órí àpáta àgbàrànsala.
Ọ̀rúnmìlà ní ẹ ṣìkẹ́un l'ójìjó rere,
K'ó mọ́ọ̀ wá.
Ọ̀rúnmìlà ní ó ń dún yùnmuyùnmu,
Ó ń kùn yùnmuyùnmu,
L'órí àpáta àgbàrànsala.
Wọ́n ní kín ni ń dún yùnmuyùnmu,
Kín ni ń kùn yùnmuyùnmu,
L'órí àpáta àgbàrànsala?

Wọ́n ní aya ní ń dùn yummuyummu,
Aya ní ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala.
Ọ̀rúnmìlà ní ẹ ṣílẹ̀kùn fúlẹ̀jọ̀ rere,
K'ó wọlé wá.
Ọ̀rúnmìlà ní ń dùn yummuyummu,
Ó ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala.
Wọ́n ní kín ní ń dùn yummuyummu,
Kín ní ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala?
Ọ̀rúnmìlà ní ọmọ ní ń dùn yummuyummu,
Ọmọ ní ń kùn yummuyummu
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala.
Ọ̀rúnmìlà ní ẹ ṣílẹ̀kùn fúlẹ̀jọ̀ rere,
K'ó wọlé wá.
Ọ̀rúnmìlà ní ń dùn yummuyummu,
Ó ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala.
Wọ́n ní kín ní ń dùn yummuyummu,
Kín ní ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala?
Wọ́n ní ikú ní ń dùn yummuyummu,
Ikú ní ń kùn yummuyummu,
L'óri àpótí àgbàrìṣàsala.
Ọ̀rúnmìlà ní ewe didinọpàbàayin,
Ni yóò di ikú nàà fún ìun.
Ọ̀rúnmìlà ní ewe didinọpàbàayin,
Ni yóò di àrùn nàà fún ìun,
Ni yóò di ofò, ẹ̀gbà, ẹ̀se nàà fún ìun.
Ọ̀rúnmìlà ní ewe didinọpàbàayin
Ni yóò di gbogbo ajogun nàà fún ìun.
Ọ̀rúnmìlà, Baba, Àgbọnnìrègún,
Ng ó pé n dìnà ire.

## Ese Ẹ̀kejo

Ọwọ̀n ìrìn ni Lmú abẹ́rẹ́ wọnú;
Ọwọ̀n ìmí ní i mú akẹ̀rẹ̀ngbẹ̀ẹ̀ wọnú;
Ọwọ̀n ọmọ ni i mú ọmọ́ jalè



'Tí wọ́n fi i pé ohi ní ń pa ó l'ode Ìdó;
Èní pọ̀ tí ó gbẹ́n,
Ẹ jẹ́ á fi wọ́n wé pààhyuni níná oko;
A dìá fún Ọwọ̀n,[1]
Tí wọn ó fi jayé ilée baba rẹ̀.
Ó ní kí wọ́n ó mú mùní ìmn jayé,
Ó ní ìmn ò kòwà Ìgùrọ̀.
Wọ́n ní kí i ṣewò ní àwọn ń wá
Bí kó ṣe gbẹ́kọ̀ọn rẹ̀ tí ó pọ̀ lápọ̀jọ.
Ni wọ́n bá mú Ọwọ̀nrin jayé ilée baba rẹ̀.
Wọ́n sọ̀pá sáràn;
Ó mú fìmin rẹ̀ jàde;
Wọ́n ya ẹnu kòtò,
Orin awo ní wọ́n ń kọ.
Wọ́n ní, 'A l'Ọwọ̀nrin jayé kàsìí o,
Ìré dé,
Yèpẹ̀dé.
A l'Ọwọ̀nrin jayé kàsìí o,
Ajé dé,
Yèpẹ̀dé.
Ẹni bímọ bíyè l'ó bímọ,
Yèpẹ̀dé.'

## Ese Ẹ̀kejo

Ẹmọ́ lùlù, ọmọ Olọ̀pàà;
Àfẹ̀bọ̀jọ, ọmọ Ìgbìrìnkù;
A dìá fún Kókó,
Tí ń lọ rèé lóyè lọ́kọ.
Wọ́n ní ìmọ Kókó,
Wọ́n ní ọ̀jọ̀ ní ó ń lọ fẹ́ yìí o,
Wọ́n ní o ń gbodọ̀ kọ ọ̀ nílẹ̀ o.
Kókó ò gbọ́.
Ìgbà àṣẹ̀bọ,
Ìgbà àtẹ̀rù,
Ọ̀jọ̀ ó rọ̀ mọ́,
Ewée Kókó ò gbẹ.
Bírà ọbọ ní i gbe ni;
Àìrà kì í gbẹ́yàn,
Kéé pé o,

Kéé jìnà,
Ẹ wáá bá wa láìkú kangiri,
Àìkú kangiri l'à á bókè.

### ATÚMỌ̀

1 *Sìngbò*: ara ẹgbà, kí àwọn ó máa sán ọ̀lẹ̀mùlẹ̀ nítorí owó tí ó kó lọ́wọ́ rẹ̀.
2 *Kọ̀ndọ̀ndọ̀*: orúkọ ìlù kan.
3 *Ọ̀ndọ̀ndọ̀*: orúkọ ọmọkan.
4 *Yàkàyọ̀*: kòókò kan tí ó bẹ̀ nínú igbó tí àwọn ọmọde fẹ́ràn láti máa jẹ.
5 *Ọ̀tọ̀n*: Ọ̀wọ́nrín Méjì.

# 7 ỌBÀRÀ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ekíní

Òní bàrà,
Ọ̀la bàrà;
A dáà fún bàrà,
Tí ń lọ sóko àlero ọdún,
Tí ń fi gbogbo ojú sùnkún ọmọ
Ojú ọmọ ní ń pọ́n bàrà,
Ó yàgàn,
Ó yàgàtà,
Ó r'ọ́mọ l'ẹ́yìn adìẹ, ó bú púrú sẹ́kún.
L'ó bá mééjì kọ́ọ̀ta,
Ó l'ọ́ọ̀ko àlòwa.
Òdú ló bímọ báyìí?
Ni bàrà dìdì sí,
Wọ́n ní pípọ̀ n'ìre ọmọ rẹ̀,
Ṣùgbọ́n kí ó rúbọ
Kí ó rúbọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ,
Kí ó sì rúbọ kí àwọn ọmọ aráyé
Ó mọ̀ pe àwọn ọmọ náà,
Ẹbọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ ni bàrà rú,
Kò rúbọ ọtá.
Nígbà t'ó rúbọ tán,
Wọ́n ní k'ó gbé ẹbọ náà lọ sí ẹ̀yìn-odi.
Wọ́n ní ibi tí ó bá gbé ẹbọ náà sí,
Ni kí ó fi ṣelé,
Kí ó sì máa gbé.
Ó sì ṣe bẹ́ẹ̀,
Ó sì bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ.
Ṣùgbọ́n nítorí ẹbọ ọ̀tá tí bàrà ò rú,
Lẹ́dọ̀ọ̀dún ni àwọn ọmọ aráyé
Ñ pa á lọ́mọ jẹ.
Àyìn-odi l'ó wàá ń yìn àwọn ọmọ rẹ̀.
Ó ní, 'Òní bàrà,

Ọ̀fà bàrà;
A dífá fún bàrà
Tí ó l'ọ̀ọ̀dọ̀ àkeù ọ̀dọ̀n,
Ríró ọbẹ ní í gbe ní,
Àtró kì í gbèyàn,
Kéé pé o,
Kéé jìnà,
Ẹ wáá wo'fá awó kí,
B'ó ti ń ṣe.
Ifá dé, ablẹ,
Ebọra abẹ,
Ọpẹ́, abẹ wàrà.

## Ẹsẹ̀ Èkẹjì

Mo jí, ọ̀kọ̀ó ń rọ́kọ,
Èmi ò lọ;
Mo jí, ọ̀dàdà ń rudà,
Èmi ò rè:
Mo jí, mo gbàràan bàbá mi lọ́wọ́;
Àràan bàbá mi ṣọwọ́ gbọgbọọgbọ;
Mo jí, mo gbé àràan bàbá mi;
Àràan bàbá mi abẹsẹ̀ gbọgbọọgbọ.
Gbọgbọọgbọ lọwọ́ yọ́ jọ́ọ̀;
Gbọgbọọgbọ ni mọ̀rìnrìn ọ̀pẹ̀ yọ́ ilẹ̀;
Gbọgbọọgbọ ni ẹ̀gan ìkẹ̀rẹ̀ yọ́ jù wọ́n;
A dífá fún Ikúrú-olé,
Ọmọ Olófinyẹ̀rẹ̀,
Ní ọjọ́ tí ń lọ lè ṣèfá fún Ọnikorogbẹ̀bì.
Wọ́n ní ó mú àkùkọ gìgìrò l'Ọ̀ṣun.
Wọ́n ní ó mú ọ̀jọ̀kọ̀jọ̀kọ ẹyẹlé l'Odù,
Ẹ̀kẹyìnjú ẹyẹ.
Ìmọ̀ Ìgbà,
Ìmọ̀ Ọ̀fà,
Ẹ wáá bá ni ní àrìṣẹ̀gun;
Àrìṣẹ̀gun l'awá wà.



## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹta

Ọ̀rúnmìlà, Ifá, mo ní ó di ọ̀ọ̀rọ̀n ìran;
Ìràn wa ni í ṣawo,
A dífá fún Ọpẹ̀
Tí yóó máa là àkàrà bí ọ̀bọ ẹrẹ̀kẹ.
Ẹ̀gbàgà, ṣulè mi ni o ṣe;
Ìmọ̀ ọ̀pẹ̀, ṣulè mi ni o ṣe.
Ọ̀rúnmìlà, Ifá l'ó fún mi lọ́wọ́ gbèlẹ̀;
Ifá l'ó fún mi lépo mú jẹ̀un;
Ọ̀rúnmìlà l'ó fún mi ní àdì bá wọ̀n,
Ifá, jí kí o wáá l'ọmọ̀ọ̀ rẹ bọ́ ní ìgbà.
Bí ọ̀pọ̀ọmpọ̀ọmpọ̀n bá tan mọ́n tiẹ̀,
Ọ̀rì ọmọ rẹ̀ ní í gbé e é lé.
Ẹ̀rìgì Àlọ̀, wá kí o wáá ṣọ̀là
Sìlé èmi awo.
Bàbá mi, Ẹ̀rìgì Àlọ̀,
Wá dandan kí o wáá ṣọ̀là
Sìlé èmi awo.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹrin

Mo jí, mo bá erin nínú igbó;
Mo ní, erin, pẹ̀lẹ́ alámọ̀ọ̀ mọ́ọ̀kan mọ́ọ̀kan.
Mo jí, mo bá ẹfọ̀n lódò;
Mo ní, ẹfọ̀n, pẹ̀lẹ́ alámọ̀ọ̀ pàsìpàsì.
Mo jí, mo bá àgbọ̀nrín nínú igbó;
Mo ní, àgbọ̀nrín, pẹ̀lẹ́, alámọ̀ọ̀ mọ̀ràmọ̀rà.
Mo jí, mo bá eré lábàtà;
Mo ní, eré, pẹ̀lẹ́ o, alámọ̀ọ̀ kìnkìnì.
Ilé ṣegbin, ilé ń lọ s'ódò ìmín!
Ikán ṣegbin, ikán wọn a ṣe Ìlọ̀ọ̀gbà.
A dífá fún ẹ̀rìnlọ́jọ ọmọ ẹrankọ,
Tí wọn ó bẹ́ Ìkàrin ọ̀gìrì,
Tí wọn ó bẹ́ Ìlàràn ọ̀kò
Wọ́n ní ẹbọ ẹbọ-ẹ̀yin ni kí wọn ó ṣe.
Wọ́n ní àwọn ò ṣebọ ẹbọ-ẹ̀yin.
Àwọn amọ̀yẹmọ̀yẹ ilé Ọ̀rúnmìlà
Ní wọ́n ṣe Ifá fún àwọn ọ̀tọ̀ Ìkàrẹ̀
Ní ọjọ́ tí wọn ó mú ẹranko kan.

Wọ́n ní kí wọn ó rúbọ,
Bí wọ́n ti rúbọ tán,
Wọ́n wọnú igbó lọ,
Ní wọ́n bá rí àwọn ẹranko,
Ní wọ́n bá bẹ̀rẹ̀ sí í pa wọ́n.
Wọ́n wáá ń yin àwọn awo
T'ó kífá fún wọn.
Àwọn awo wọn wáá ń yin Ifá,
Bíró ẹbọ ni í gbà ni;
Àìrú í gbèèyàn,
Ẹ wáá wáá bá ni ní àrúṣẹ́gun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kasàrún

Ọ̀rúnmìlà, babá kí mi nìkí,
Mo jẹ́ baba nìkí;
Ọ̀rúnmìlà kí mi nìkí,
Mo jẹ́ baba nìkí.
Baba l'ó t'ohun dúdú ra dúdú;
Baba l'ó t'ohun pupa ra pupa;
Baba l'ó t'aràá l'ó r'Ẹ̀gbá;
Baba l'ó t'ohun funfun l'ó ra funfun;
Baba l'ó ta Fúlàní ródòdò;
Baba l'ó tatàá l'ó ra Lárúbáwá;
Baba l'ó t'ẹrú u l'ó fi rọmọ;
Baba l'ó t'ẹ̀kùnà s'ẹ̀kùn kan pìrìnà,
A dìá fún Olómù apẹ̀rẹ̀n,
Ọmọ ọlọ́rọ̀ agogo.
Ní ọjọ́ tí ó bẹ lááràn ọ̀tẹ̀,
Tí ó bẹ lááràn ọ̀tá rẹ̀.
Wọ́n ní ó kàalẹ̀,
Ó jẹ̀ẹ,
Ẹbọ ni ó ṣe.
Ó gbọ́ rírú ẹbọ,
Ó rú;
Ó gbọ́ èrù àtùkẹ̀sù,
Ó tù;
Ó gbọ́ ìkarara,
Ẹbọ ba fọn un.



Ó ní Ifá dé, alàṣẹ,
Ẹbọra alàṣẹ,
Kò mọ̀ mọ̀ sí àrúnmọlẹ̀ bí Ifá.

## Ẹsẹ Ẹ̀keḷú

Baba Abíríyánú,
L'ó bí Abíríyánú;
Baba Abíríyánú,
L'ó bí Abíríyánú;
Baba Abíríyánú,
L'ó bí bàbá ọlẹ́wà àpéàn kọọrọ.
Bàbá ọlẹ́wà àpéàn kọọrọ
L'ó mọ ibi tí ikú pa bàbá Abíríyánú sí.
Ó ní òun ó bá mọ
Ibi tí bàbá Abíríyánú kú sí;
Ó ní òun ó bá mọ
Ibi tí bàbá Abíríyánú wà,
Ó ní òun ó bá bá wọ́,
Òun ó bá bá mu;
Ó ní òun ó bá lọ rẹ̀é
Bú fún olórìṣà òun náà àì.
Ajá gbọ́, ajá ń jorí;
Ògún gbọ́, Ògún ń jẹ̀gẹ̀dẹ̀ lájà.
Ajá tí ń jorí,
Ajá kú.
A dìá fún Ọ̀rúnmìlà,
Níjọ́ tí ó lọ rèé t'àyé Olúfẹ̀ sọ bí igbá.
Ǹjẹ́ kín ni ó t'àáyé Olúfẹ̀ sọ bí igbá?
Ẹ̀là wooroowàìyì.
Ní yóò t'àyé Olúfẹ̀ sọ bí igbá.
Ẹ̀là wooroowàìyì,
Ifá mí yóò tún ìlàrìn wa ṣe.
Ẹ̀là Ìsòdì.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Gbìrìgbìrì ni à á yìdò;
Gbìrìgbìrì ni à á yí ìkòkò;
Ìyí n yìdò,
Kí á mọ̀ mọ̀ yí ìkòkò:

Bí a ṣí ìkòkò,
Ìmú aláṣọ a bàjẹ́;
Odò ni igi,
Ìkòkò l'omọ,
Ọkàn gbogbo pọ̀rọ̀ l'Olúòrun dùn mọ́
L'ọ̀nà ọ̀kọ̀.
Bí ó bá di mẹ́jì,
A d'ọ̀ḳàṇ;
Bí ó bá di mẹ́ta,
A di gọ̀ọ̀ǹkọ̀;
Bí ó bá di mẹ́rin,
A d'àjàgbilà;
Ẹ̀kàrùn ni tùkùtùkù;
Ẹ̀kẹ́fà ni Ifá ọkọ̀ òun
Kò mọ nnkan ṣe.
Ẹ̀kéje ni Ifá ọkọ̀ òun
L'ó ti kò iyì ṣe òun lọ́wọ́
Tí òun fi d'ẹni tí ó dà bàyìí.

### Ẹsẹ Ẹkẹjọ

Ó ṣe wọ́lọ̀wọ́lọ̀, ọwọ́ mi ọ̀tún;
Ó rò mìnì, ọwọ́ mi òsì;
Ewu kòkò mẹ́jì
Ní í ba'na wọn pẹ́lẹ́ngẹ́ pẹ́lẹ́ngẹ́ pẹ́lẹ́ngẹ́;
A dá fún Ọba Àdó,
Ẹ̀jìgbòrò ìkẹ̀kọ́,
Tí ó lọ réé bá wọn múlẹ̀ ilẹ̀dá.
Wọ́n ní ó kiàki Mọlẹ̀,
Ó jàre,
Ẹbọ ni ó ṣe.
Ó gbọ́ rírú ẹbọ,
Ó rú;
Ó gbọ́ èrù àtùkẹ̀ṣù,
Ó tù;
Ó gbọ́ ìkarara,
Ẹbọ ba fín un.
Ó wáà ń yin àwọn awo rẹ̀,
Àwọn awo rẹ̀ ń yin Ifá;



Ó ya ẹnu kótó,
Orin awo l'ó bọ́ sí i lẹ́nu;
Ẹsẹ̀ tí ó nà,
Ijó fà á.
Ó ní, 'Àwá dúnlẹ̀,
A ó bá rọ̀,
Àwá d'àpẹ̀rín ilẹ̀;
Àwá dúnlẹ̀ bí Àdó;
A d'Ìgbà òkè.
A lọ gbọ́ngbọ́n.'

# 8 ỌKÀNRÀN MÉJÌ

### Ẹsẹ Èkíní

Ọ̀kànràn kan yìí nìkan, ìrè dé.
Ewé àjàǹfolé ni yóò fa ibi nù fún wa,
Ewé ẹ̀jẹ̀rìn wẹ́wẹ́ ni yóò wẹ́ ẹ dànù.
Ewé ìtapàrà l'ó ní kí ibi ó ta nù l'ára mi.
Ọ̀rúnmìlà mèku, mẹ́ja,
Ọ̀rúnmìlà m'ẹ̀yẹ, m'ẹ́ran mẹ́jìmẹ́jì,
Ó wẹ̀'rìí rẹ̀,
Ó mọ́ kedere.
A diá fún Ọlọ́fin;
Ọlọ́fin ó rantẹ̀;
Àmọ̀ràn ayan rẹ̀ ń gògbògbò ìràn;
Ọ̀kinbí, ọmọọ rẹ̀ ń ṣàrùn ọ̀rẹ̀ngẹ̀dẹ̀.
Onídùdú gba dúdú;
Onífunfun gba funfun;
Aláyìnrín gbàyìnrín;
Ìbaraqotá, wáá kíníin gbogbo lọ.

### Ẹsẹ Èkejì

Arùjẹ̀rùjẹ̀ ìjàkùn,[1]
Ìjàkùn nàà mùjẹ̀rùjẹ̀;
A diá fún Erin,
Tí í ṣe ọmọ Olúgbó;
A diá fún Ẹfọ̀n,
Tí í ṣe ọmọ Olọ́ọ̀dàn;
A diá fún Ìràngùn mẹ́ẹ̀,[2]
Tí í ṣe ọmọ Olúìràn Ìràngùn.
Wọ́n ní kí Erin ó rúbọ,
Kí ẹran ó lè baà kọ̀ọ̀.
Wọ́n ní kí Ẹfọ̀n ó wọ̀yẹ̀,
Kí ó lè baà níyì.
Wọ́n ní kí Ìràngùn mẹ́ẹ̀ ó rúbọ
Kí ó lè baà lèrú ju gbogbo ẹyẹ oko lọ.
Erin gbọ́,
Erin rúbọ;
Ẹfọ̀n gbọ́,
Ẹfọ̀n wọ̀yẹ̀;
Ìràngùn mẹ́ẹ̀ rúbọ,
Wọ́n ní lẹ́rú ju gbogbo ẹyẹ oko lọ.
Ọwọ́ Erin tẹ gbà,
Nítorí ó rúbọ dìẹ̀dìẹ̀;
Ọwọ́ Ẹfọ̀n tẹ ìyí,
Nítorí ó rúbọ pẹ̀pẹ̀ pẹ̀pẹ̀ rẹ̀gẹ̀dẹ̀;
Ọwọ́ Ìràngùn mẹ́ẹ̀ tẹ ẹrù
Nítorí gbọ̀ọ̀ rẹ̀ kò tó ìkan.
Ẹ wúré wá,
Ẹ wáà gbèyí fún mi.
Ẹni ní Ìràngùn mẹ́ẹ̀.
Ẹ wúré wá,
Ẹ wáà gbèyí fún mi.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Bí a bá ti ko re,
Bẹ́ẹ̀ ni à á kí re;
Bí a bá ti kí rà,
Bẹ́ẹ̀ ni à á jẹ́ ni;
Ọ̀rúnmìlà pẹ̀lẹ́ o,
Ọmọ alẹ̀pa lọ́pọ̀,
Ẹ ó jàdì.
Ọ̀rúnmìlà, Ẹ̀là, pẹ̀lẹ́ o,
Ẹ̀kùn ìgtan sùn.
Ọ̀rúnmìlà pẹ̀lẹ́ o,
Ọmọọ pòìpò-tàaro;
Ọmọọ ràn mí lẹ́wọ̀,
N gbẹ́rùn lẹ́ sẹ̀gì.
Awo t'ó bá tètè dé,
Wọn ó mùn rẹ̀ kó sẹ̀gì.
Ẹyí tí kò tètè sẹ̀,
Wọn a rẹ̀ẹ̀ kẹ̀yìn.

Sùgbọ́n ni ng ó kú,
Ng ó kúnlẹ̀.
Ẹ̀jìgbàrà ìlẹ̀kẹ̀ ni ng ó kú,
Ng ó kà'kún ìkú gbọ̀ọrọ̀.
A dífá fún Ìrẹ̀-ni-ń-ó-kóò,
Tí í ṣ'ọmọ Olódùmarè.
Adìẹ funfun, ìgbín ìtẹ́yọ̀ àkàṣọ.
Ta ni lè f'Olódùmarè lọ́bọ̀?
Ẹni mọ̀ d'adìẹ funfun,
Àgbà àáyá Olódùmarè.

## Ese Ẹ̀kẹ́rin

Kékeré ọwọ́, wọ́n ó jẹ́ ìbọ̀rọ̀ ùmọ̀mọ̀:
Olúm ìrère ni í y'olú lápò,
Olúm hòhorò ni í yọ ọ̀kà nínú apò;
A dífá fún òkò ìtẹ́yà,
A bù fún Ìjìmèrè,
Wọ́n ń lọ s'óko ọdẹ.
Ṣùgbọ́n, kòlòkò mọ̀ mọ̀ kú o,
Kí àgùnlẹ̀rẹ̀ mọ̀ mọ̀ yo.
Ní ìwọ̀ọ́ ìmọ̀dún,
K'á rìn jọ gbáàtẹ̀rẹ̀.

## Ese Ẹ̀karùn

Ìdáà, omo Àkrò,
L'ó dífá fún Àkrò.
Ọ̀gàràndalẹ̀, omo Ajerò,
L'ó dífá fún Ajerò.
Erékan ni í kú,
Ilé a ṣe bẹ̀ẹ̀ a si dabora,
Awo Olówu,
A dífá fún Olówu, ajíyọ̀ọ̀.
Ó ní gbìndin gbìndin l'à á rọ̀lẹ̀;
Gbẹ̀dẹ̀gbẹ̀dẹ̀ l'à á rókun
Wọ́n ní ayé Ifá ó bọ̀ wáá yalùn
Ọba nínú ìjẹ̀gẹ̀dẹ̀ tán,
Ayé ó tutùn bọ̀ wá o,
Ìjẹ̀gẹ̀dẹ̀, ìjẹ̀gẹ̀dẹ̀, ìjẹ̀gẹ̀dẹ̀.



Ṣùgbọ́n b'ọ́rí bá le ìgrùn o,
Ọ̀gẹ̀dẹ̀ wáá dẹ orí ọ̀hùn fún mi,
Ọ̀gẹ̀dẹ̀.
Bí ìkín bá le lẹ́rùn o,
Òdídẹ̀ wáà lẹ sẹ́ dẹ'kùn ọ̀hùn fún mi,
Òdídẹ̀.
Baba agọmọ títí ti dé Mọ̀jàlawa;
Baba gọ̀jọ̀bọ̀ kanda, Mọ̀jàlawa;
Ẹyẹ ni wọ́n rí,
Wọ́n ni kóòkò mọ̀ rako;
Ẹyẹ ni wọ́n rí,
Wọ́n ni kòlòdò mọ̀ rado mọ̀.
Wọ́n mọ̀ ẹtí,
Wọ́n fi bá ẹyin alágẹmọ.
Wọ́n pàjìnlà ẹtí,
Wọ́n bẹ́ orí akàn lódò.
Wọ́n dé Ìròṣà,
Wọ́n b'Ólùkè l'ábà Ọ̀ṣun,
Ẹrù ọmọ ìṣẹ̀ṣẹ̀.
Wọ́n l'ára àwọn gbọ̀kan gògòògò,
A dífá fún wọ́n ní Lómù, apọ̀ràn,
Ọmọ ọba tí í pa wọ́n lẹ́gàn jẹ.
Àsìnghà l'ọwàa rÒmù.
Ẹrù ó bá nìnájù;
Ẹrù ó bá lẹ́yìn;
Àṣẹ l'ára babaláwo lẹrù nà.
Ẹrù ni ìbín,
Ẹrù ni ọ̀hùn,
Ẹrù lààrin gìngìrìn;
Ọ̀kànràn bí o bó kàn kon,
O sì pa ò pìnpìnrì;
A dífá fún Ọ̀kànràn
Tí yóò ṣohun ẹ̀rù,
Tí wọ́n ó fi jìn ín pàdìpàdì.
Kín ni yóò wo'lẹ̀ ndì fùnọ?
Ẹjì Ọ̀kànràn ni yóò wo'lẹ̀ ndì fùnọ.
Ọ̀tẹ̀ awo, ndì awo,
E ó òdìi kàngàrì lò wọ́n pa mọ̀lẹ̀.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Kẹ̀kẹ́ logún, mọ ilé Olówu;
Àbùjà logbọ̀n, awọn wọn ìnlé Ẹyọ̀.
Tìre làdàjìa;
A dìá fún Olùnlòyè.
Tí ń tikọlé ọ̀run bọ̀ wá sí tayé.
Nígì, Olùnlòyè mọ́ mọ́ bínú o,
Olùnlòyè mọ́ mọ́ ṣe r'ẹ̀dùn ọ̀rùn.
Bí kíyà ti ń pọnmọ
Lanírè ò sí mọ pọ̀n.
Olùnlòyè mọ́ mọ́ ṣe r'ẹ̀dùn ọ̀rùn
Àgbà tí kò bínú lọmọ ẹ̀ rẹ̀ pọ̀.
Àìpẹ́, àìjìnà,
Ẹ wáà bá ni ní wìjẹ̀ ọmọ.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Jìnìjìpe, jìnìjìpe:
A dìá fún Ṣàngó,
Ọmọ Ọ̀gbojà.
Wọ́gbà ti ń bọ̀ lẹ́àrin ọ̀tà.
Wọ́n ní ó kòkì Mọ́lẹ̀,
O jàre,
Ẹbọ ni ó ṣe.
Wọ́n ní ó rú ẹ̀gbẹ̀lẹ̀ ọ̀kà,
Kí ó rú tàsígaurau kan àti digí.
Ó rúbọ tán,
Wọ́n ṣe Ifá fún un.
Ó ṣẹ́gun sí ọ̀tún;
Ó ṣẹ́gun sí òsì.
Bí ó bá ti ẹ̀jọ̀ yàán,
Gbogbo ayé ń túká ni.
Ifá wáá kẹ̀ fún un pé
Kó gbọ̀dọ̀ bá àwọn ọmọ òun jà.
Ó yà ọmu lọ́ọ̀,
Ọmọ awo ni ń kọ.
Ó dọmọ̀ ẹ, Àrìrà.
Ilẹ̀ awo dọmọ̀ ẹ, Àrìrà.



Àì rìrò o,
Àì ṣèlẹ̀;
Bí Ṣàngó bá parọ,
Ilẹ̀ l'ó dà.
Àìrìrò o,
Àìṣèlẹ̀.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Ọ̀rúnmìlà l'ó di rekete,
Ògún rekete l'ọ́jà ọpọ̀n:
Iwọ̀jà oni, gẹ̀gẹ̀ ni ì máa ṣe gún;
Ẹ̀yìn oni, gẹ̀gẹ̀ ni ì máa ṣe gún.
A dìá fún Àlàbúṣe
Tí ì ṣe awo Àlàbílẹ̀ẹ̀
Kèè pẹ́ o,
Kèè jìnà,
Ẹ wáà bá wa láilúkẹ́gun.

## ATỤMỌ̀

1 *Ìjòbìní*: orúkọ ìlàkùn kan.
2 *Ìràwọ̀ mọ́tà*: orúkọ ẹyẹ inú igbó kan.
3 *Ọ̀ọ̀ràbẹ̀ẹ̀*: igi kan ni t'ó ṣe bìṣìṣí.

# 9 ÒGÚNDÁ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Kanranjàngbọ̀n, awo inú igbó;
Ìjàkùn wọ̀rọ̀wọ̀, awo ọ̀dàn;
Màmọ̀ Màmọ̀, awo òjúlé,
A dìá fún Ẹ̀rigi Àlọ̀
Tí yóò jagbọ̀n ohì.
Kí Ẹ̀rigi Àlọ̀
Ó tóó jagbọ̀n ohì tán,
Ifá ní ire gbogbo
A máa wọlé tọ ni.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Babá dó lÓkò,
Baba a rìn lÓkò,
Baba a ṣojú bọ̀nkọ l'àlọ̀de Ọ̀jọ̀kò;
A dìá fún irinwó mọlẹ̀ Olúkọ̀tùn;
A kì fún irinwó mọlẹ̀ Olúkòsì.
Wọ́n ní kí wọ́n kàsálọ̀,
Ẹbọ ni kí wọ́n ó ṣe.
Ǹjẹ́ ẹbọ kín lakápò ń ṣe?
Ẹbọ àìkú lakápò ń ṣe.
Ifá mọ̀ mọ̀ jẹ́ kí akápò ó rìn lọ dànù.
Ẹ̀rigi Àlọ̀, mọ̀ mọ̀ jẹ́ kí
Ikú akápò ó bàjẹ́,
Ifá mọ̀ jẹ̀ẹ́ kí akápò ó rìn lọ.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ọ̀rúnmìlà rìnrìnrìn nínú ìgẹ́.
Ó ní ojú kì ìpọ́n ju kokonkuò lọ;
Ọrùn kò gbọ́dọ̀ wó ju pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀;
A dìá fún Ògún,
Onìjà-oòkè.



Ẹ̀jẹmu Olúwọmọn,
A dì girigirì relé ìjà,
A dìá fún Ọ̀rúnmìlà,
Bara Àgbọnmìrègún,
Ifá ń sunkún ìran ò lápá
Tí a ń ṣi gagbùn.
Àṣẹ ìgbà Ògún di ní silẹ̀
Lara tóó rọ ni,
Ìgbà Ògún di ni silẹ̀ rèé,
Lara tóó rọ ni.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Bí ni mo ti jáde rìí,
Ọ̀nà mi ni mo sì ń tẹ̀lé lọ;
A dìá fún Ògún,
Onìjà oòkè,
Ẹ̀jẹmu Olúwọmọn,
A dì girigirì re'bi ìjà.
Babaláwo l'ó wí pé
Kí n mú mọ̀ padà délé mọ̀;
Gbọ̀ọrọ̀gbọ, ògbọ̀ọrọ̀gbọ ni kí n bá ọ̀kùn rẹ̀,
Gbọ̀ọrọ̀gbọ.
Ọ̀ṣọ̀ìgùn l'ó ní kí n mọ̀ padà délé mọ̀;
Gbọ̀ọrọ̀gbọ, ògbọ̀ọrọ̀gbọ ni kí n bá ọ̀kùn rẹ̀,
Gbọ̀ọrọ̀gbọ.
Ọ̀kùnrin, obìnrin, ọmọdé, àgbà, oníṣé, àlejò,
L'ó ní kí n mọ̀ padà délé mọ̀,
Gbọ̀ọrọ̀gbọ, ògbọ̀ọrọ̀gbọ ni kí n bá ọ̀kùn rẹ̀,
Gbọ̀ọrọ̀gbọ.

### Ẹsẹ Ẹ̀karùn

Wọ̀rọ̀kọ̀ wọ̀rọ̀kọ̀ ni wọ́n rọkọ̀;
Wọ̀rọ̀kọ̀ wọ̀rọ̀kọ̀ l'à ń tàdá,
Lèdèlè lèdèlè ni l'à á r'agogo idẹ,
Ilì ó ba dòkò, a dọ̀kan;
A dìá fún Ọ̀rúnmìlà,
Níjọ́ tí Ifá ń bẹ láàrin ọ̀gìrì,
Tí Ifá ń bẹ láàrin ọ̀tá.

Ifá ó p'àsàmọ̀jọ̀n[1] gbọ̀ọ̀rọ̀
Tí yóò kọ́ṣẹ ọ̀tá dà sí.
Ọrúnmìlà ní, 'Ńjẹ́ tundrè tontyọ̀,
Ẹnun wọn sùùnsùùnsùùn,
Ẹnun wọn.
Àkìtìbàjọ̀, àlàtì,
Ẹnun wọn sùùnsùùnsùùn,
Ẹnun wọn.'

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

À bí lọ,
À bí dè;
À bá rọ̀rán àní,
Ìjà ni ìbí dè;
A dìá fún Àkókó Mọ́jàlawo,
Tí ń ṣawo r'òde Ọ̀yọ́.
Àkókó, awo ọba l'òde Ọ̀yọ́.
Kólówọ́ o jòmìà 'lé.
Àrọ̀nì jòmìà 'lé Olókọ̀yí;
Kólówọ́, o jòmìà 'lé bẹ̀ẹ̀rẹ̀be.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ìgbòròkí, omo Ìgbòròkí;
Ìgbòrọ̀fà, omo Ìgbòrọ̀fà;
Ńjẹ́ tí Ìgbòròkí ó ti kí wọn l'òde Ìgbòròkí mọ́,
Ní ọjọ́ tí Ìgbòrọ̀fà ó ti kí wọn l'òde Ìgbòrọ̀fà;
Pọ́ọ̀pọ́lọ̀,[2] abìdí ṣàṣikì;
A dìá fún Akìpà, ọmọ Àrò;[3]
A bù fún Mulómàghìjà, ọmọ Ọ̀dọ́fin.[4]
Mulómàghìjà, ọmọ Ọ̀dọ́fin,
Ìwọ l'o dìjà sílẹ̀ fún Ìwààmìkààyìn
Tí í ṣe ọmọ Ẹ̀rí Adà.
Ìwọ l'o f'òkúlẹ̀ mọ́ran l'ọ́bẹ̀ ìkó.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Àbọ̀mọ̀lẹ̀ rìkán abaja regán regàn;
A dìá fún Ọ̀bẹ̀yí ọ̀kọ́kọ́,
Agbàghà ẹrẹ̀, Àtàrùghà ẹ̀ kọ̀pẹ̀.



Ńjẹ́ tí ó umbóin àìrìbì,
Tí ó gbààwọ́ àìrìpọ̀n;
Tí ó l'ọwọ́ ominu nù'gìrì gbìgbe.
Wọ́n tíì ọba ní kí ó wáà rí,
Kín ni ìmọ ó ba rú bàyìí?
Wọ́n ní kí ó rú àgbébọ̀ adìẹ mẹ́jì,
Kí ó sì rú ẹgbàájìlélógún.
Ó rúbọ tán,
Wọ́n se Ifá fún un.
Ó sì bí ọmọ̀lọ̀pọ̀ ọmọ.
Ìjó ní ó jó,
Ayọ̀ ní ó yọ̀;
Ó ń yìn àwọn awo rẹ̀,
Àwọn awo rẹ̀ ń yìn Ifá;
Ó ya ẹnu kótó,
Orin awo ní ó kọ,
Ó ní, 'Ọ̀bẹ̀yí bọ̀gìn;
Ọ̀bẹ̀yí bọ̀gbọ̀n;
Ta ni kò mọ̀ ní pé
Ogún ọmọ ó tó Ọ̀bẹ̀yí.'

ATÚMỌ̀

1 *Pàsàmọ̀jọ̀n*: ṣe kòsímọ̀jọ̀n; dá ìgbò.
2 *Pọ́ọ̀pọ́lọ̀*: ọ̀nàkọ̀ igi àlà kan.
3 *Àrò*: oyè ìlú kan lààrin àwọn Ọ̀gbóni.
4 *Ọ̀dọ́fin*: ọ̀nàkọ̀ oyè kan ní ìyí náà.

10 # ÒSÁ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kínní

Kẹ́rẹ́jẹ Ọwinrin,
Ọwinrin kẹ́rẹ́jẹ;
A díá fún Ọ̀rẹ̀ yèkètè
Tí ń ṣọmọ r'ode Ìwòrò.
Wọn ní ẹbọ ni kí ó ṣe
Kí ó lè baà láje jù ẹgbẹ́ rẹ̀ lọ.
Ńjẹ́, a ó láajé kíjé
Bí ará ìde Ìwòrò;
Kẹ́rẹ́jẹ Ọwinrin,
Ọwinrin máà kẹ́rẹ́jẹ.
A ó láaya kíya
Bí ará ìde Ìwòrò;
Kẹ́rẹ́jẹ Ọwinrin,
Ọwinrin máà kẹ́rẹ́jẹ.
A ó bímọ bímọ
Bí ará ìde Ìwòrò;
Kẹ́rẹ́jẹ Ọwinrin,
Ọwinrin máà kẹ́rẹ́jẹ.
A ó l'óhun gbogbo
Bí ará ìde Ìwòrò;
Kẹ́rẹ́jẹ Ọwinrin,
Ọwinrin máà kẹ́rẹ́jẹ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Ẹlẹ́nu méjì ń já n'ínú ìbàrà, ìrùbà ìrùbà;
Ẹlẹ́nu méjì ń já n'ínú ìbàrà ìrùbà ìrùbà;
A díá fún ọ̀bu Àjàní,
Tí ń lọ rè'dìí àbíkú.
Ó dẹ̀hìn tán,
Ó ní n bọ̀ yìn o,
Ẹ gbọ̀bẹ̀.



Ẹyin ọmọ,
A bọ̀ yìn o,
Ẹ gbọ̀bẹ̀.
Ẹ má ṣe fàbíkú ṣeléé wa mọ́ o,
A bọ̀ yìn o,
Ẹ gbọ̀bẹ̀.
Ẹyin ọmọ,
A bọ̀ yìn o,
Ẹ gbọ̀bẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Igbá ìwọ̀ṣì,
Igbá ìwọ̀ṣì;
A díá fún Mọ̀nìyere igbá ìgò.
Nígbà ìgò ní ìpọ̀njú Mọ̀nìyerè mọ́,
Bí ó bá dígbà ẹ̀ẹ̀rùn tán;
Wọn a di onígba nkan,
Wọn a donígba ìdẹ.
Ẹrò Ìpo,
Ẹrò Ọ̀fà,
Ẹ wáá bá ni ní ìṣẹ́gun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Bí ó bá ṣe wí pé
Gbogbo ọ̀rẹ̀ gbogbo ni í sun póò,
Ìrókò gbogbo ìlú ni tán nígbó;
A díá fún igba ọ̀rẹ̀,
Tí ń t'Ìkọ́lé ọ̀run bọ̀ wá sí tayé.
Bí ó bá ṣe wí pé
Gbogbo ọ̀rẹ̀ gbogbo ni í sun póò,
Ìrókò gbogbo ìlú ni tán nígbó;
A bá fún Òwìrì
Tí ń t'Ìkọ́lé ọ̀run bọ̀ wá sí tayé.
Òwìrì l'à ń jà,
Gbogbo wa,
Òwìrì l'à ń jà.
[illegible] pan'rí mọ́n bá wà pọ̀.

Ọwẹ́rẹ́ l'à ń jà,
Gbogbo wa,
Ọwẹ́rẹ́ l'à ń jà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kaàrùn

Àfin, awo Ìlódè;
A dá fún Ajìbọ̀là
Tí í ṣe yèyé ẹlẹ́kuru
L'ọ́jà Ẹ̀jìghìmẹ̀kùn.
Ajìbọ̀là ṣ'ayé òní ire;
Ọ̀rúnmìlà l'ó ní kí o ṣ'ayé òní rere.
Ajìbọ̀là ṣ'ayé òní rere;
Ẹ̀làṣòdè l'ó ní kí o ṣ'ayé òní rere.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Mo gbélé fojú sùn ọ́,
Ni í ṣekú pa babaláwo;
Mo gbé ọ̀dẹ̀ fàniyàn sùn ọ́,
Ni í ṣekú p'àwọn àgbà ìṣègùn;
Ó ń rí í bílé ti rí wọ̀nyí bí;
Ọmọdé wọ̀nyí ò jẹ́ kí n sùn;
A dá fún Ọ̀rúnmìlà,
Wọn ní ọdún yìí
Ni ọdún ọ̀làa babaà mi pé.
Ìbìrà ẹbọ,
Ẹrù àtùkẹ́ṣù;
Ẹ wáà bá mi ni àrúṣẹ̀gun.
Àrúṣẹ̀gun l'àwá wà.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ìṣẹ́ l'ó ṣẹ́ igún,
Ni orí igún ń pá;
Ọ̀ṣì l'ó ta àwòcò orìṣà,
Tí ó fi fi'wo ọ̀rùn kéyin ṣẹ̀ngẹ̀nrẹ̀ngẹ̀n,
Tí ó fi ńi ọmi tí ó ìunkoó kíri;
A dá fún Olúbàsí,
Tí í ṣe ọmọ Aláràn òde Ìbìrà;



Ọ̀gbẹ̀rẹ̀wà ni babaa rẹ̀ẹ́ jẹ́,
Wọ́n ní kí wọ́n ó dámọ̀ jẹ,
Kí wọ́n hun agbọ̀n ìdẹ fún wọn
L'ótù Ifẹ̀ rèrè.
Wọ́n ké sí Igbá,
Tí í ṣe ọmọ Onírèsè
Pé kí ó wáá hun agbọ̀n idẹ.
Igbá rè ìsàn ò mọ̀ agbọ̀n idẹẹ́ hun.
Wọ́n ké sí Ataare
Tí í ṣe ọmọ Oníkogbòn
Tí ìlú Ìkógbà.
Ataaré ní òun ò mọ̀ agbọ̀n idẹẹ́ hun.
Wọ́n wáá ké sí Akíngàkán
Tí í ṣe ọmọọ wọn l'ódò Òkèrèèrì.
Akíngàkán l'ó wáá hun agbọ̀n ìdẹ fún wọn
L'ótù Ifẹ̀ rèrè;
Ni wọ́n fi ṣe ayẹ́e wọn,
Ni ayẹ́e wọ́n fi gún gẹ̀rẹ̀gẹ̀rẹ̀
Kò ṣàwo nígbà yí mọ̀,
Ọmọ Ẹ̀fọ̀n l'a ké ràwo dìẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Orí burúkú kì í wú túúlú;
A kì í dá ẹsẹ̀ aṣiwèrè mọ̀ lọ́nà;
A kì í m'orí olóyè lawùjọ;
A dá fún Mọ̀hòorù,
Tí í ṣe obìnrin Ògún.
Orí tí ó jọba lọ́la,
Ẹnìkan ò mọ̀.
Kí tọkọtaya ó mọ̀ pèrèn wọn
Ni wèrè mọ̀.
Orí tí ó jọba lọ́la,
Ẹnìkan ò mọ̀.

11

# ÌKÁ MÉJÌ

## Ẹsẹ Èkíní

Ẹlẹmẹ̀kà, Àyìnàmẹ̀kà;
Ọwàràǹkàkà, ọwọ́ àgbọn ò rọ̀;
Kàkà kò rọ̀ Ẹ̀ẹ̀yọ̀,
Lílo ní ó le bí ọrùn akika,[1]
Bí ọrùn akika;
Awọn ni wọ́n tẹ Onikàá Ìkà nífà;
Wọ́n tẹ Onikàámògùn nífà;
Wọ́n tẹ Àrò Ìkà nífà;
Wọ́n tẹ Ọ̀dọ́fin Ìkà nífà.
Àrò Ìkà kì í jajà;
Ọ̀dọ́fin Ìkà kì í jàgbò;
Onikàámògùn kì í ìjẹ àwùkọ.[2]
Ó ń kà mí lẹ́gẹ̀dẹ̀;
Ó ń kà mí lìwùnà;
Bí wọ́n pé kí o mọ́ ka a,
O kà a.
Ìyá Ìkàlègun;
Baba ni Akàtigùn;
Èyí tí wọ́n ń pè ni Akàkàkàgbunà,
Tí í bá wọ́n gbé akuika òkùta.
Ìbókun ni ìpòòyí kàjà.
Ó pòòyí kà,
O bá wọn d'ode Ìkà.
O bá wọn nibi tí
Wọn gbé ń forí ọkàǹ lọ̀mú.

## Ẹsẹ Èkejì

Kín l'ó fi ayọ ìkà ṣe?
Ó fi ayọ ìkà bora.
Ó wáà ó jẹ àkàrà kàjà,
Ó jẹ àkàrà kà,
Ó lọ s'ode Ìlàkà?
Ó gbé alákàgbà[3] wálé.
Ó fi ìkaraluun borí mọ.
Ó ń lọ s'ọ̀dọ̀ Làkaì.
Ó gbé alákàgbà wálé,
Ó sọ pàlùn kan kàǹkà sójà.
Ó ń rìn kàǹi kàǹi kànìi lọ l'ode Ìkà
Wọ́n ní ẹ̀rí ṣe
Tí o fi ń rìn kàǹi,
Tí o fi ń rìn kàǹi,
Èé ṣe tí o ń rìn kàǹi kàǹi kàǹi kanà
Lọ l'ode Ìkà?
Ó ní ìbòòsì[4] apá òun ni ó kàyé.
Ó wá èyí tí yóò ṣe, kò rí,
Ó kò ẹyẹlé pọ̀ mọ́ ìdìẹ,
Ó wá èyí tí yóò ṣe kò rí,
Ó gbé kàǹà,
Ó fi bọ̀'lẹ̀ ọkà.
Ó ní kàǹà òun
Ó bá ọkà ńlẹ̀.
Ọkà ni kí ó máa kakọ,
Kí ó máa lakọ.
Ó ní kàǹà òun ti gbé kàrà kàǹà wálé.
Ó kà kàà kò,
Ó ka kàrò kàrò;
À dìíà fún Ọlọ́fin, ọ̀ọ̀ ngbò;
À dìíà fún Ọlọ́fin, kankan-wóò.
Ará Nàkìnọndi, ará Ìgbó Ònìtó;
Ọnà tóótóòtóò òbẹ̀ erìnrà,
Ó bínú kanlé èkè l'ókè Àgùnpopo?[5]
Ó l'Ìgbórí la ilẹ̀ èkè kàǹkà,
Ìwọ l'o dùrò un,
Ìwọ l'o bẹ̀rẹ̀ un;
Adégorítẹ́; Adégoníyè,
Òkòkónkò, ta l'ó le bá Ṣàngó kògun?
Ẹlẹ́ l'ó fi gbóná n'ilẹ̀ àràá rẹ̀,
L'ó fi kangba ajòkè.
Ó dà bí ọmọ ṣe!
Ẹ mọ́ fìnín Ṣàngó lọ́mọ mọ́;
Òràn ó pọ̀pọ̀ọ̀pọ̀.

Kí ó mọ̀ tí ọnípẹ̀,
Kò sí ẹni tí yóò dúró
Ṣe onípẹ̀ fún Ṣàngó.
Òkè ni yóò dúró,
Igbó kò gbọdọ̀ dúró.
Bí igbó bá dúró,
À jó igbó tagbatagba.[7]
Bí òkè bá dúró,
A so òkè kèrè kalẹ̀.
A gbé àlàlà ori kaná.
Òkòkònkò, ta l'ó le bá Ṣàngó kógun?

## Ese Ẹ̀kẹta

Ó ní atòni aréré,
Pàkòyí,[7] babaa Mọ̀gànà.[8]
Bí òjò bá ń rọ̀,
Ẹyẹ oko cé kọ́,
Ẹyẹkẹ́yẹ ọ̀rọ̀ kóé mọ́,
Ẹyẹ òjé gbóde.
Àdán òkó ni i ṣe kòròkòtò
Ní gbogbo ẹyẹ fi yára wọ́ṣẹ dúró,
Ng ó réyán ti n lọ s'ilé Aláró,
Kí ó bá mi kí Wingbòlú,
Ọmọọ wọn n'ilé Aláró.
Ng ó réró ti n lọ sí Ẹ̀jìgbòkòrò,
Kí ó bá mi kí Òrìṣàlúlú,
Ọmọọ wọn l'ode Ẹ̀jìgbò.
Kí ó kí Ẹ̀gúnbíyìí,
Ọmọ Ọ̀lọ́ọ̀ndá Ogbójò
Ilá ká reké,
Ọmọ ẹran ṣìnì.
'Tí í yẹ ọ̀lẹ̀ lóko,
Ọmọ fèfọ ti í fọ̀ dídùn l'Ẹ̀gún.
Ọjọ́ a kólù sílẹ̀ l'ẹ ń rẸ̀gún
A bá aṣọ̀ sínú ilé fún ọmọ Ẹ̀kẹ̀ọra.
Ṣe bí ọ̀pọ̀ ńlánlá
Ni wọ́n fí í lo gbòdù àràn fún ayaba.
Olọ́run ò lápẹ̀sẹ̀,[10]
Enìkan ò bọ̀ sọ́jọ́.



Ó ni ó ti ri,
Bí a ti dá ọlà tán,
Ni a dá erin.
Bí a ti dá Jẹ̀yẹ̀[11] tán,
Ni a dá Odùduwà,
Ọmọ lèkeré wọ́n ń tàkìtì kú nẹ̀;
Àgbààgbà wọ́n ń tàdéé kú nẹ̀;
Ọmọ lèkeré, wọ́n jó wéléwẹ́lẹ̀,
Àgbààgbà ń l'ọ̀pá àrẹ̀ẹ̀[12] kalẹ̀.

## Ese Ẹ̀kẹrin

Afẹ́fẹ́ ń fẹ́ l'òkè ihin;
Afẹ́fẹ́ ń fẹ́ l'òkè ọ̀hún.
Ọrún ń mì tìtìtì,
Wọn ò mọ̀'hi ti ó ṣọlẹ̀ sí.
Gbogbo ayé ń mì kìjokìjo.
Ọrun ìhìhìn kì í wó,
Kí ó lọ sí ọrun ìhọ̀hún;
Ọrun ìhọ̀hún kì í wó,
Kí ó lọ sí ọrun ìhìhìn.
Hà, a ò r'ọ́wọ́ọ̀ mi.
Ìṣẹ̀ rẹ ni mo ń ṣẹ̀ kiri.
Ng ó jẹun tí mo fi dé'lé Olú,
O ò r'ọ́wọ́ọ̀ mi.
Hà, Ìṣẹ̀ rẹ ni mo ń ṣẹ̀ kiri.
Àtẹ̀lẹwọ́ọ̀ mi rèé, Hà,
Ng ó mu tí mo fi d'ókè Ọrà,
Hà, o ò r'ọ́wọ́ọ̀ mi,
Ìṣẹ̀ rẹ ni mo ń ṣẹ̀ kiri.
Ng ò jẹ,
Ng ò mu,
'Ti mo fi dé òkè Ìgẹ̀ti, ilé Àgbọnmìrègún.
Hà, a ò r'ọ́wọ́ọ̀ mi.
Àtẹ̀lẹwọ́ọ̀ mi rèé, Hà.
Ìṣẹ̀ rẹ ni ń ṣẹ̀ kiri.
Hà, mo gbọ́ pé
'Tiìrí l'ó ń ṣe fún ọ̀wọ̀.
Hà wálà ni ràn s'àyà mi.

Ilà mo gbọ́ pé
Àkókọ́yọyọ̀ l'ó ń ṣe fún Ọwá ọ̀gá,
Ogìrì gbọ́ọ̀n,
Ọwá, ọmọ onre yoyò.
Ǹjẹ́ mo bá kú,
Ọmọ ni kí o jẹ́ kí
O fọ́rín rọ mí kèl dandanlan.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹ́ẹ̀rin

Ìgun ọgọ ni í forígbún ìgun ilé;
Sòbìà ni i dìbí ẹran ìmù;
A diá fún Ọ̀nkànmógún,
Ọmọ akinorikò inú ẹtu.
Ní ọjọ́ tí ó sunkún
Wí pé ọmọ ò rí ọ̀bìnrin fẹ́.
Wọ́n ní kí ó sùré tete,
Ẹbọ ni kí ó wáá ṣe.
Agẹ́ àkù ẹbọ ní í gbe ni,
Àìrú kì í ghèéyan,
Kèè pẹ́ o,
Kèè jìnà,
Ìtà ní ẹ wáá bá ni
Ní wọ̀wọ̀ ire aya.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ajá gbó lóko
Bẹ́ẹ̀ ni wọn ò gbọ́ nílé;
Àmèrè ní í jẹ oko ìgbẹ́ lófẹ̀ẹ́;
Èṣù ni í gba ẹbọ,
Bẹ́ẹ̀ ni kò mọ Ifá dá;
A diá fún Jàmùjàmú
Tí yóò máa dá ọmọ ni giri kìginjọ́.
Àgbààgbà popòó dẹ̀rù;
E jẹ́ kí Jàmùjàmú ó dẹ̀rù,
K'ó máa lọ.
Ojúde ni bàbáké bá ìlọ̀;
Àgbààgbà dẹ̀rù;



Kí Jàmùjàmú ó dẹ̀rù,
K'ó máa yára lọ.
Abọ̀jìgbìn kì í kó sọ́ọ̀ Ẹ̀gùn.
Àgbààgbà dẹ̀rù;
Kí Jàmùjàmú ó dẹ̀rù,
Kó máa yára lọ.
Dòbọ̀kòkọ kì í kó sí'ojò ọkọ.
Àgbààgbà popòó dẹ̀rù;
E jẹ́ kí Jàmùjàmú ó dẹ̀rù,
K'ó máa yára lọ.

## Ese Ekeje

Ajá gbógbóógbó lóko,
Ìgbọ̀ọ̀ wọn ò dìlé;
Apójùbà kò mọ ilé ọrọ́;
Ojú abuyin kò tólẹ̀ ìmàle rẹ;
A diá fún òkè
Tí ó bẹ líbrin ògìrì
Tí ó bẹ líbrin ọ̀tá,
Òkè ó bẹ líbrin ògìrì,
Òkè á bẹ líbrin ọ̀tá,
Ó ké gbọnyin gbọnyin.

## Ese Ẹ̀kejọ

Ẹ̀yin wòrowòro a tà ìyere;
Ẹ̀yin rìdìrìdì a tà àkù;
Ẹ̀yin bíi wèrè
Ní í bá wèrè pàdé.
A diá fún Ọ̀nìwèèrè
Wí pé kí ó mọ̀ bọ́ọ̀ ṣe dèédèé àti ojó-ọ̀nà.
Kò sí ìyàtọ̀ nínú alárìnkọ
Àtiwọn tí kò tètè rí.
Rírú ẹbọ ní í gbe ni,
Àìrú kì í ghèéyan,
Ọ̀nìwèèrè ṣe bẹ́ẹ̀ ó bá'kò lọ.

1 *Àbùbú*: mkọ; ẹranko onípọ̀pọ̀ kan.
2 *Òṣùkọ*: ìtíríkọ.
3 *Ẹ̀bìtì*: ìdílégbò kan ní Ìlú Ọ̀yọ́.
4 *abìkàgbá*: alákan; adán.
5 *Ó ní ìkòóò*: ó farawe ta, ó kó ìkó ọdún.
6 *Àgbàgbọ̀*: ìdílégbò kan ní ìlú Ọ̀yọ́.
7 *ìtagbatagba*: ìgbà jẹ̀ ìtákùn kan tí ó lìgbánu tí ó ń bẹ nínú igbó.
8 *Pèlébírí*: ìjọyè kan ní ìlú Ọ̀yọ́.
9 *Mọ́gàjí*: Àwọn tí ń lọ ọ̀dẹ̀ Lángbàsà.
10 *Ìpòrì*: ìkan nínú àwọn ìlú fún Ọ̀rúnmìlà.
11 *Jẹ̀yẹ̀*: Ẹ̀gbọ́n Olódùmarè.
12 *ọ̀pẹ̀ ìrọ̀rọ̀*: ọ̀pẹ̀ ìsàlẹ̀ tí àwọn àgbà awo máa ń fà kọ́lẹ̀.



# 12 ÒTÚÚRÚPỌ̀N MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Afọ̀kẹ̀ ní ó ṣe ìgì oko báyìí bí;
Ẹ̀lẹ́mọ̀ìlẹ́ẹ̀ ní í yowé ìgbagbà yagbayagbo;
Èdídí méjì ń jà l'òkè odò,
À ó mako, a ó mabo;
Wọ́n ṣetan wọn lókè,
Wọ́n ṣetan wọn lókè;
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà,
Bá ó lọ rèé ṣe ìkà nÍfá;
Yóò si fi Àrùn ṣe ojúgbẹ̀mìí.
Bí Ọ̀rúnmìlà bá lọ,
Bí ó bá ṣe ìkà nÍfá;
Tí ó sì fi Àrùn ṣejúgbẹ̀mìí;
Àṣẹ, Ifá, ìdí máa kápò fún ọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Tẹ́kẹ̀ẹ́, ọmọ Ilé;
Ìgbìnọ́rà, ọmọ Ọ̀ta;
Akípàsìnlẹ̀dẹ̀ Fò lọ̀lẹ̀;
Tí ó kan ilẹ̀,
Tí ó kan òkè,
Ó kojúu rẹ̀ mòlódo;
A dífá fún Oyèrọ̀kà,
Ọmọ Ìwàrẹ̀fà n'Ífẹ̀,
Tí bẹ̀bẹ̀ rẹ̀ẹ̀ fi ṣìkẹ̀ ní ròwerònu,
Ìgbà tí wọ́n kò ríran mú ṣìkẹ̀,
Ó bá pòrì ṣẹ́kùn.
Ó ní b'ókù ní wọn kọ́ọ̀ fi í ṣìkẹ̀,
Ng ó mọ̀;
Ìgbà òrun, ẹ yára wá gbàrò ẹ̀ ṣe.
Bí ọ̀jọ ni wọ́n kọ́ọ̀ fi í kẹ̀kẹ̀,
Nè ò mọ̀;

Ìgbà ọrun, ẹ yára wáà gbarà yí ṣe.
Bí ẹyẹ ni wọn kọ́ọ́ fi lẹ́lẹ̀,
Ng ó mọ̀;
Ìgbà ọrun, ẹ yára wáà gbarà yí ṣe.
Bí ẹran ni wọn kọ́ọ́ fi i lẹ́lẹ̀,
Ng ó mọ̀;
Ìgbà ọrun, ẹ yára wáà gbarà yí ṣe.

## Ẹsẹ Ẹkẹta

Ọgbọ́n inú ọkọ́gbọ́n,
Ni ọkọ́gbọ́n fi ń jẹun;
Aṣìrí ẹ̀yìn kò mọ
Ìmọ̀rán ara rẹ̀ẹ́ gbà;
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà,
Baba ó lọ rèé bá ọmọ mọ́lẹ̀ ní ìdúdó.
Kèè ṣẹ́ o,
Kèè jìnà.
Oko Àgbọnmìrègún wáà dodò,
Ó ń ṣàn lọ bí ọba ẹrẹ̀kẹ.
Àgbọnmìrègún ni gbogbo ohun tí mo bá ṣe,
Kí ẹ mún fi hùn mí.
Ajálalẹ̀ ni ti wọ̀ọ̀rọ̀wọ̀.
Bí erin bá y'ọwọ́ ìjà lálẹ́,
Orí aran rẹ̀ ni í kà a ò lé.
Ìka kan ṣoṣo ní í k'orí ohun bọ́nà.
Eyì tí kò sunwọ̀n ẹ̀yẹ̀lé,
Orita ni í gbé.
Eyì tí kò sunwọ̀n ìkẹ́ṣa àkù,
Ẹ̀ẹ̀kùlé ni í wà.
Mo fi ewé ohun,
Mo fi ṣe ohun jẹ.
Ohun burúkú kì yóò lèè bun mí.
Ewé ọrọ̀, wọn kì í lunlẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Akiti l'ó fi ẹyin jọ ere,
Bẹ́ẹ̀ ni kò lèè wọ̀ ìiri;
B'ójòlá bá tí ń fà lọ̀gàn,
Gbogbo araa rẹ̀ ni í máá kọ
Bíi tòm, bíi tòm;
A dífá fún Arágẹ́ọ́run
Tí ó sunkún wí pé
Òun kò nílé,
B'ónílé bá kọ́lée rẹ̀ẹ́ lẹ̀,
A tì'ilé ọgbọ́n,
Ẹniọ̀lẹ́nì ni í rù ìpákà lágọ.

## Ẹsẹ Ẹkarùn

Orógbó kéré, bẹ́ẹ̀ ni kò ní awẹ̀;
Àgbáyun abẹ́ra mẹ̀rẹ̀wọ̀rẹ̀ kẹ̀gẹ̀ẹ;
Ẹyẹ àlùkùnrìn abiyẹ́ ìlàmì lanni;
A dífá fún Ṣẹ̀ṣẹ̀ngìdì
Tí ó sunkún òun kò rọ́mọ bí.
Wọ́n ní ó kàalẹ̀,
Ó jàre,
Ebọ ni kí ó ṣe.
Ẹnikan kì í fẹ̀ ọmọ́ kú lẹ́yìn Ṣẹ̀ṣẹ̀ngìdì.
Ọmọ wẹ́rẹ́wẹ̀rẹ̀ n'ilé àlàdì.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ọ̀rúnmìlà, ewo Ayé,
L'ó dífá fún Ayé;
Ní ọjọ́ tí Ayé ń sunkún òun ò lẹ́nikan.
Pẹ̀rẹ́pẹ̀rẹ̀[1] ewo Àlàn,
L'ó dífá fún Àlàn,
Ní ọjọ́ tí ó sunkún wí pé òun kò lẹ́yìn.
Ọ̀rúnmìlà ní à máa wò,
A ó ní ọpẹ̀ rí.
Ayé ni ń ṣe wọn báyìí bí?
Ma mú ìgbon,
Ma fi b'ọrùn mi.[1]
B'ó bá tùbọ̀ ṣe gìdà,
B'ó bá tùbọ̀ ṣe gìdà;
Ma mú ẹyinlá,
Ma mú b'ọrùn mi.
A dífá fún Gbogbolóhun,
Tí ó ṣawó r'àpá òkun, ìlàjì ọsà...

Gbogbolobón mọ́ dé,
Ẹbọ́ dà.
Gbogbolobun kòì dé,
Ẹbọ́ kò.
Gbogbolobun.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Bí aríìgbò kosún,
A t'ọwọ́ panú;
Bí ọ̀gọ̀ọ̀lọ̀[1] kosùn,
A sì fi ru pea wìrìwùrìì;
A dìá fún wọn l'óde àìgbọ́n,
Ọgbọ́n a pa wọn lọ́wọ́ bí abẹ.
Kéé pé o,
Kéé jìnà;
Ẹ wáá wo'lé ayé kì,
Ifá ti ó ṣẹ.
Ifá dé, alóṣe,
Ẹbọru, abòṣe;
Ọpẹ́, abòṣe mààrà.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Dìẹ̀dìẹ̀, ni ì ṣẹ́ san,
Kẹrẹ̀kẹ̀rẹ̀ ni ì ṣẹ́ dẹ.
A dífá fún omọ̀ Ọ̀ṣà,
Tí ó rrgbéo mọlẹ̀ Lésin.
Ó tubọ kà ayé.
Ó san nígbà yí o.
Igba ni ewé akìsan,
Kò ṣàì san ju ti ẹ̀gbẹ̀ẹ̀.

### ATÚMỌ̀

1 Ọ̀gọ̀ọ̀lọ̀: ẹyẹ pẹ́ńkí kan lààrin ẹ̀ṣọ̀ Balanbọ̀ọ.
2 K'ọ́pàsa ọ̀ṣ: Ìṣọ̀ ọ̀run ti tìmú. Bàbá tábí lyá ẹni tí ó ti kú ni a ń pè ní ọ̀run ẹni.
3 Ọ̀gọ̀ọ̀lọ̀: ọmọde tí ó ti tó bí ọmọ ọdún mẹ́jìdínlógún títí lọ sí nkan bí ọdún mẹ́ẹ̀ẹ̀dógbòn.



# 13 Ọ̀TÚÁ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Ọ̀túá kan ṣoṣo ni wọ́n dá s'ójú ọpọ́n,
Bí ó bá di méjì, a di òdodo;
A dìá fún Odìdẹrẹ́,
Tí í ṣe aya Àgbọnmìrègún.
Wọ́n ní odìdẹrẹ́,
Ọ̀kọ́ọ̀ rẹ ńkọ́ o?
Ó ní ó bẹ nílé o,
Ẹ kú o.
Wọ́n tún ní odìdẹrẹ́,
Ọ̀kọ́ọ̀ rẹ ńkọ́ o?
Ó ní ó bẹ nílé o.
Ọkànrin dùdú Okè Igẹ̀tí;
Ọmọ Adóo bàbá tí í n'ọwọ́ oògùn.
Babá dìmú kotá;[1]
Babá dìmú koono;[2]
Babá dìmú koyá;[3]
Babá dìmú ko ògànbọ̀rọ̀[4] yẹẹyẹ̀ẹ̀yẹẹ.
A dìá fún ọmọ Ọ̀pẹ̀
Tí wọ́n ní yóò ṣubú lààrin ọjà.
Gbogbo ẹ̀ru, ẹ dìgbò h'ọ̀pẹ̀,
Èmi l'ẹ ó l'ọpẹ̀ lọ?
Àrìrà ó p'ọpẹ̀,
Inú ó ní í p'ọpẹ̀ ní òkan.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Kótópọ̀ kékèké bálẹ̀,
Wọ́n a l'ara yí kọọrọ
A dìá fún bàbá Mọ̀kẹ̀,
Abẹ̀wò gọ̀rọ̀jọ̀,
Babá ó ó bí Àmọ̀yàn lọ́mọ.

Baba a tú mi;
Baba a tú kiko;
Ó bórín búrin tú bòjbùę.
Wọn ní kí ó rù eku méji olùwéré,
Wọn ní kí ó rù ẹja méji olùgbàdà.
Ó ní eku méji olùwéré;
Obìnrin rẹ̀ ní ẹja méji olùgbàdà:
Kò tó fún ọkọ òun mọ́.
Ó ní kí ó kòkó rèjó.
Ewúrẹ́ méji abàmú ẹyẹ̀rẹ́yẹ̀.
Ní wọ́n bá tẹjú
Ewúrẹ́ méji abàmú ẹyẹ̀rẹ́yẹ̀.
Bàbá Mọ́kì ní òun ní àtàtàntà;
A tú ìbeji s'ínú ilé òlà.
A tú ìbeji s'ínú oko gbẹ̀rẹ̀gẹ̀.
Bí wọ́n ti ń bí mi,
Ní wọ́n ń bí lóko,
Bí ẹ bá rí méji awo,
Bẹ́ẹ̀ ẹyin ò mọ awo.
Òtún l'ó ti tú ìbeji s'ínú ilé òlà.
Ẹ bá rí awo,
Bẹ́ẹ̀ ẹyin ò mọ awo.

## Ese Ẹkẹta

Ji-ngiri ní í fi gbogbo ara jókòó;
A dífá fún bàbá Mọ̀le,
A bí'ọwọ́ gẹ̀rẹ̀gẹ̀
Ti yóò fi ayé gbogbo ṣọ̀fẹ̀ jẹ.
Wọ́n ní ó kírúbọ̀,
Ebọ ni kí ó ṣe.
Ìgbà t'ó rúbọ tán,
Ti ayé yẹ ẹ́ tán,
Ó ní ọ̀fẹ̀ ni ng ó máa jẹ;
Ọ̀fẹ̀ n'Ìgúnún jẹbọ,
Ọ̀fẹ̀ ni ng ó máa jẹ;
Ọ̀fẹ̀ ni Àkàlàmọ̀gbò jẹ oko,
Ọ̀fẹ̀ ni ó mọ jẹ;
Ọ̀fẹ̀ l'Ìgúnún bọ̀lọ́jọ́ jẹ kàrìn ilú.



## Ese Ẹkẹrin

Ọjọ́ ìkan ò ní í bani,
K'ó mọ́ koó lẹ́ ilẹ̀ẹ́ ìkẹ́ lábẹ́ná;
Àwòkènùlù ojú-ọrun ò lọ̀ kọ̀nko;
Ọmọ ìgbàlẹ̀ ò yá kú sìrí wọ̀.
Fún àwọn ọmọ ẹlẹ́gbẹ́ẹ̀;
A dífá fún Olókun, ọ̀ọ̀ní adé,
A-gbódó-jòba.
Ní ọjọ́ tí gbogbo ayé ní
Àwọn ó bá Olókun ṣe mọ́,
Ẹ bá mi ṣe kinní,
Ẹ bá mi ṣe.
Ekú aṣọrọ l'ó ní kí
Ẹ bá mi ṣe,
Eku olòsè l'ó ní kí
Ẹ bá mi ṣe kinní,
Ẹ bá mi ṣe.
Bí mọ́rìwò bá ṣọ̀ lókè,
Ojú Olódùmarè ní í kojú sí.
Ẹ bá mi ṣe kinní,
Ẹ bá mi ṣe.
Àmọ̀, àìgbàrà,
Ẹ wá l'orí bálẹ̀ f'Olókun,
Òkun l'ayaba ìmú.

## Ese Ẹkarùn

Ẹyẹlé l'ó fò kòkè,
Wọn ó máa fò lẹ́ngẹ́ lẹ́ngẹ́,
Wọn a fi ìbòòbò jẹ àdàbà;
A dífá fún ako ẹyin
Nígbà tí ó sunkún ọ̀rí pé:
Òun ò lóbìnrin.
Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Ẹ wá bá ni ní àrùṣẹ̀gun;
Àrùṣẹ̀gun l'àwá wà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ọ̀bá mugbó àìkú;
Ọ̀bá mùrè àìkú;
Alámọ̀ tí í mọ orí Olú
Kí í jẹ́ kí ó fọ́;
Alápatà ẹ̀kùrin aṣọ̀nà;
A dìá fún Ọ̀rúnmìlà,
Bá ó bẹ lâàrin ìgbìnì ọ̀tá.
Ọ̀rúnmìlà ní ẹ mọ̀ pariwo mi mọ́.
Ẹnìkan kì í pariwo orí,
K'ó mọ̀ lọ̀ lamrun.
Ẹnìkan kì í pariwo adìẹ ògògòrò,
K'ó mọ̀ lọ̀ hu iyẹ́.
Àjẹ́ tí ò bá mú ọ̀tá,
Ẹ sìn lẹ́yìn mi.
Bí a bá f'ẹ̀nìkọ̀ rokorokò,
T'ó bá fi yà,
À sìn lẹ́yìn rẹ̀.
Àjẹ́ l'ó bá ó ṣe mí,
Ẹ sìn lẹ́yìn mi.
Bí akèrèngbè bá fọ́,
Ẹni t'ó fi ò pọn omi,
A sìn lẹ́yìn rẹ̀.
Ẹ mọ̀ pariwo mi mọ́,
Ẹ sìn lẹ́yìn mi.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Àkùkọ t'ó kọ lónàà,
Ìkọ rere l'ó kọ;
A dìá fún Ìki,
Tí ó ṣomọ n'Ìlé Aládà,
Ẹwí, ọmọ arùm Ọ̀jọ,
Ẹwí, ọmọ arùm ẹ̀gẹ̀ẹ̀gẹ̀.
Àkùkọ t'ó kọ lónàà,
Ìkọ rere l'ó kọ;
A dìá fún Gbọ́ndọ̀pi,



Tí ó ṣomọ r'Òde Ìjẹ̀ṣà.
Àkùkọ t'ó kọ lónàà,
Ìkọ rere l'ó kọ;
A dìá fún Orìtà,
Tí í ṣe aya Ọ̀rúnmìlà.
Tí ó sunkún ọmọ ó r'ọ́mọ bí.
Wọ́n ní ó kàrálẹ̀,
Ó jàre,
Ẹbọ ní ó ṣe.
Ìgbà t'ó rúbọ tán,
Wọ́n ṣe Ifá fún un.
Ó bí ọmọ mẹ́ta;
Obìnrin sì ni àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.
Ó rántẹ̀ẹ́ s'Ílé Aláró,
Ó ní òun bímọ mẹ́ta,
Obìnrin sì ni wọ́n.
Ó rántẹ̀ẹ́ sí Ajerò,
Ó ní òun bímọ mẹ́ta,
Obìnrin sì ni wọ́n.
Ó rántẹ̀ẹ́ sí ọọ̀n l'Óde Ìjàyè,
Ó ní òun bímọ mẹ́ta,
Obìnrin sì ni àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.
Orúkọ èkíní ni Wúrúkù-ma-jàdẹ;
Orúkọ èkejì ni Wọ̀rọ̀kọ̀-bí-ogún-à;
Orúkọ ẹ̀kẹta ni Òdèrè-kì-í-ṣọ̀sọ̀.
Àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀tà dàgbà tán,
Wọ́n ní àwọn ó sálọ lọ ní ọjà Ìjàyè;
Tí Orìtà lọ́ọ̀ àwọn ndé ti wá.
Àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀tà sì ti di ẹni ọ̀kùnrin.
Èkíní ru ẹ̀fọ̀ yànrin;
Èkejì ru ẹ̀fọ̀ tẹ̀tẹ̀;
Ẹ̀kẹta ru ẹ̀fọ̀ ewúro.
Wọ́n lọ sí ọjà,
Tí ilẹ̀ ti ṣú,
Wọ́n ò dé.
Nígbà tí ilẹ̀ ọjọ́ kejì mọ́,
Ni Orìtà, aya Àgbọnmìrègún, bá rúra,
L'ó bá lọ sí ọ̀nà ọjà Ìjàyè.
Ó pàdé àwọn ẹrò ọjà lọ́nà.
Ó ní ẹrò ọjà,

Ẹ bá ìmn ri ọmọ ìmn bi?
Ìjàyè.
Wọn ni orúkọ ọmọ rẹ ti í jẹ?
Ìjàyè.
Ó ni ọ̀kan Wùrùkù-mo-jìnde;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Wọ̀rọ̀kọ̀-bí-ọgún-lé;
Ìjàyè.
Ó ni ọ̀kan Òdèrè-kì-í-sọ̀rọ̀;
Ìjàyè.
Wọn ni Ọsìn pàkan sàgbàlá;
Ìjàyè.
Ọsìn pàkan sí Mògùn;
Ìjàyè.
Ọsìn pàkan sẹ̀kùlé;
Ìjàyè.
Ó na àdó mọ̀lẹ̀,
Gbogbo àwọn ẹrú ọjà kú lọ bẹẹrẹbẹ.
Ni Otùtù bá tún gbéra,
Ó lọ sí ìdìrin ọjà wọn.
Ó ni ẹyin ẹrú ọjà,
Ẹ bá ìmn rí àwọn ọmọ ìmn?
Ìjàyè.
Wọn ni orúkọ ọmọ rẹ ti í jẹ?
Ìjàyè.
Ó ni ọ̀kan Wùrùkù-mo-jìnde;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Wọ̀rọ̀kọ̀-bí-ọgún-lé;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Òdèrè-kì-í-sọ̀rọ̀;
Ìjàyè.
Wọn ni Ọsìn pàkan sàgbàlá;
Ìjàyè.
Ọsìn pàkan sí Mògùn;
Ìjàyè.
Ọsìn pàkan sẹ̀kùlé;
Ìjàyè.
Ó ni ayé ra lónìí,
L'ó bá na àdó kan mọ̀lẹ̀,
Ni gbogbo àwọn tí ó bẹ lọ́jà bá kú.



L'ó bá wọlé Ọsìn, ọba wọn lọ.
Ó ní Ọsìn, ó bá ìmn r'àwọn ọmọ ìmn?
Ìjàyè.
Ọsìn ni orúkọ ọmọ rẹ ti í jẹ?
Ìjàyè.
Ó ni ọ̀kan Wùrùkù-mo-jìnde;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Wọ̀rọ̀kọ̀-bí-ọgún-lé;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Òdèrè-kì-í-sọ̀rọ̀;
Ìjàyè.
Ọsìn ni òun pàkan sàgbàlá;
Ìjàyè.
Òun pàkan sí Mògùn;
Ìjàyè.
Òun pàkan sẹ̀kùlé,
Ìjàyè.
Otùtù ni ayé ra lónìí,
L'ó bá lẹ àdó kan mọ̀lẹ̀,
Ni Ọsìn, ọba Ìjàyè, bá kú.
Ni Otùtù, aya Àgbọnmìrègún, bá lọ s'ọ́dọ̀ Iyá Ọsìn.
Ó ni Iyá Ọsìn, o bá ìmn rí ọmọ ìmn?
Ìjàyè.
Iya Ọsìn ni orúkọ ọmọ rẹ ti í jẹ?
Ìjàyè.
Ọ̀kan Wùrùkù-mo-jìnde;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Wọ̀rọ̀kọ̀-bí-ọgún-lé;
Ìjàyè.
Ọ̀kan Òdèrè-kì-í-sọ̀rọ̀
Ìjàyè.
Iyá Ọsìn ní ọmọ òun pàkan sàgbàlá;
Ìjàyè.
Ó pàkan sí Mògùn;
Ìjàyè.
Ó pàkan sẹ̀kùlé;
Ìjàyè.
Otùtù, aya Àgbọnmìrègún, ní ayé ra lónìí,
L'ó ba lẹ àdó kan mọ̀lẹ̀,
Ni Otùtù àti Iyá Ọsìn bá jọ wọ ìjẹ̀kuli.

Wọn jàjàpá títì,
Ẹnikan ò dá ara wọn.
Nígbà tí wọn ó rí ẹnikan là wọ́n,
Ni wọ́n bá wẹ́ pọ̀,
Ni wọ́n bá di agba ìmọ̀ ìgbó.

### Ẹsẹ Ẹ̀keji

Ajìrọ minimini ní í ṣe ọmọ Ògún;
Ajìrọ túlú ọmọ Òkiti Ẹ̀fọ̀n;
A dífá fún Lágbo Ọ̀gìgà,
Tí ọyẹ́ ó rò
Gẹ́gẹ́ bí ìfá tí í ro ni.
Wọ́n ní ó kàbọ̀,
Ó jàre,
Ẹbọ ni kí ó ṣe.
Ẹrú Ìpo,
Ẹrú Ọ̀fà,
Ẹ wáá bá ni ní tìṣẹ̀gun.

### ATÚMỌ̀

1 *hool*: ko itẹ; ìrẹ̀ jẹ́ igi hun.
2 *hoore*: ko ìrore; òrore jẹ igi kan.
3 *boyal*: ko iyà; ẹyà jẹ igi ọdẹn kan bẹ́yẹ̀.
4 *àpàsẹ̀kẹ̀*: igi nlá kan ni ẹyí nṣà.



## 14 ÌRẸTẸ̀ MẸ́JÌ

### Ẹsẹ Ekini

Babalàwo ìtẹ̀rẹ̀, itẹ̀rẹ̀;
Babalàwo gbàlàjà bí ìkẹ òwú;
A dífá fún Ìrẹtẹ̀,
Tí yóò tẹ mẹ́jì lẹ́ẹ̀kàn,
Ìrẹtẹ̀ tí ó tẹ mẹ́jì
Tí ó fà yẹbẹyẹbẹ bí ọba ẹrẹ̀kẹ̀.
Ǹjẹ́ kín ni ó tẹ mẹ́jì?
Dẹdẹrẹ;
Ìrẹ̀ ni ó tẹ mẹ́jì,
Dẹdẹrẹ.
Tí a fi lájẹ̀;
Dẹdẹrẹ;
Ìrẹ̀ ni ó tẹ mẹ́jì,
Dẹdẹrẹ.
Tí a fi lóyo;
Dẹdẹrẹ;
Ìrẹ̀ ni ó tẹ mẹ́jì,
Dẹdẹrẹ.
Tí a fi bímọ;
Dẹdẹrẹ;
Ìrẹ̀ ni ó tẹ mẹ́jì,
Dẹdẹrẹ.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Kùkùndùkú ẹ̀ẹ́wẹ́ gẹ̀rẹgẹ̀rẹ;
Ọ̀pàlọ́pọ̀ mìgùn a sì ma ṣọmọ gbẹ̀rigbẹ̀;
Bí o l'ọ́pọ̀ ológun,
Bí o ní ẹ̀kẹ́,
Kò ní í jẹ́;
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà,
Baba ó lọ kọ́ gbé Agúnbìogà aláyaà.

Agúnbiọsà, aya mọ,
Ọ̀rúnmìlà l'ó gbé Agúnbiọsà níyàwó;
Agúnbiọsà, aya mọ,
Ọ̀rúnmìlà l'ó gbé Agúnbiọsà níyàwó;
Agúnbiọsà, aya mọ.
Bàbá wọ́n rántíẹ́ sí Akínlọ́dún,
Awon wọn l'óde Ilọ̀dún;
Ó rántíẹ́ sí Akínfálà,
Awọn wọn òde Ifálà.
Gbogbo wọ́n dé,
Wọ́n wá ó ṣe:
Agúnbiọsà, aya mọ ò,
Agúnbiọsà, aya mọ;
Ọ̀rúnmìlà l'ó gbé Agúnbiọsà níyàwó;
Agúnbiọsà, aya mọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kọta

Afọlunpamọ́ ni í ṣàmì ọna;
A dífá fún Amure
Tí ó lọ s'óko àlerò ọdún.
Tútú-lọgọ́n, awo Àjàkírun;
Sísì-lọgbọ́n, awo Àjàkírun;
A dífá fún Òkè
Tí í ṣe ọmọ Onifọn ọ̀run.
Nígbà tí Òkè ń tọ̀run bọ̀ wáyé,
Ó pàdé Afọlun-pamọ-ní-í-ṣàmì-ọ̀nà,
Ó sì bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀ pé
Ṣé ó lee yẹ òun báyìí?
Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó ṣe.
Òkè sì rúbọ.
Nígbà tí ó rúbọ tán,
Awọn awo rẹ̀ ní kí ó mú ilẹ̀
Nínú ẹbọ tí ó rú náà,
Kí ó gbé e sí ẹ̀bá ọ̀nà,
Kí ó sì ṣe àmì rẹ̀ dáadáa.
Wọ́n ní nígbà tí ó bá d'óde ìsálayé,
Yóò bàá mọ rẹ̀ ní ẹ̀bá ọ̀nà.



Nígbà tí Òkè d'óde ìsálayé tán,
Kò tíì ṣe ohunkóhun
T'ó fi bẹ̀rẹ̀ sí í wá ọ̀nà ọ̀nà kiríkiri,
Tí ó ń wò fẹ̀rẹ̀fẹ̀rẹ̀.
Nígbà tí àwọn ọmọ aráyé rí i,
Wọ́n bi í sí pé
Kín l'ó dé t'o fi ń wo
Ẹsẹ̀ ọ̀nà fẹ̀rẹ̀fẹ̀rẹ̀ bẹ́ẹ̀?
Ó ní àwọn Afọlun-pamọ́-ní-í-ṣàmì-ọ̀nà,
L'ó dífá fún òun Òkè,
Nígbà tí òun ń tọ̀run bọ̀ wáyé.
Njẹ́, ìbòn ni ng ó gbéé dà,
Ọbọ́n ni ng ó gbéé dà;
Òkè a tọ̀nà tààrà dà sí etí ọ̀nà.
Nìbi tí Òkè dà sí,
L'ó ti ń gbọ̀ọn,
L'ó ti ń gbọrọ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ìbaàbà ni à ń gbé ọ̀pọ̀n;
Ìbaàbà ni à ń mọ ilé;
A ó ti ṣe mọ olóri màrìwò màrìwò
Ni à á pe babaláwo.
Ìbaàbà ni obìnrin tọ̀ọ́ l'óde Ọ̀tẹ̀.
Ọ̀pọ̀n wá òde Ọ̀tẹ̀,
Mo kí ọ.
Bí ẹ bá ní irú,
Ẹ mú irú wá fún mi.
Bẹ́ ẹ kò sí nírú,
Ẹ mú ìgìrì wá òde Ọ̀tẹ̀;
Ìgbà tí Ìrẹ̀ ń mẹ́jì,
Ní òde Ọ̀tẹ̀,
L'a tóó rìre.

## Ẹsẹ Ẹ̀karùn

Àgbò' ń ṣebà làgbò;
Ògidan' ń ṣebà lọ̀gìdan;
Ìpèrè' ń ṣebà lìpèsè;

A dá fún Olú Òrò
Tí ó di ọkàn ọrọ̀ lé Ọ̀ni kiri.
Mo fẹ́ ẹ̀ lá,
Ẹ má ṣe kà mí.
Bí ng ó bà ká,
Ma lá.
Mà à mọ̀ lówó;
Mà à mọ̀ bímọ;
Ẹmọ kà sàlà.

## Esẹ Èkẹfà

Lá tiwili tiwili;
Lá tiwili tiwili;
Bí ọ́ bá balẹ̀ a gbọ̀tán;
Lá balẹ̀ a gbóò;
Òde gbangba ò tenùn
Fún 'mọ́dẹ̀ wọnyí jòkòó;
Ajì rọ̀ ọmọ ìkán ìdàn;
Àdẹ̀ fi ìyẹ́ ṣòrọ̀;
Ẹyẹlé fi ìrugun ṣẹ́mu;
A dá fún wọn l'òde Ẹ̀gbà,
Nibi tí wọn gbé fi igi ìmù ìgbò ṣe ìwìn bọ.
Nibi tí wọn gbé fi ìrọ̀ki àgbò bọ Orò.
Wọ́n ní kí wọ́n rú ẹbọ
Nitori ọmọ tí yóò jogbó jàù.
Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà;
Ẹ wáà bá ni ní tiṣẹ́gun.

## Esẹ Èkeje

Kí à tọ́ ẹ́ mọ̀rọ̀,
Àwa ara ẹni fún ara ẹni;
A dá fún Ọ̀rúnmìlà
Ní ọjọ́ tí ó ń lọ sí Ifẹ̀.
Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà ń lọ sí Ifẹ̀,
Tí ó fẹ́ẹ́ mọ̀ bí ìran ó rìí ọ̀pọ̀ òòyàn
Tí yóò bàá òun wà sí ibi
Tí òun tẹ̀dó sí.



Ó wáà dìtù fún ara rẹ̀,
Bá ní kí ó rà ajá kan fún igi òṣùṣú,
Àgbò kan fún Òkè,
Ó ní ẹbọ náà,
Ó kọrí sí òde Ifẹ̀.
Nígbà tí wọn ọ̀tà rẹ̀ẹ́ rí i,
Wọ́n ní kò ní í rí ẹni bá a dúró;
Ọ̀rúnmìlà ní òun tí rúbọ.
Àwọn ọ̀tà rẹ̀ẹ́ ní
Ajá ni yóò gbó o;
Àkùkọ ni yóò fi kàn;
Àgbò ni yóò kàn ìn.
Ọ̀rúnmìlà kò fi etí sí tí wọn.
Ó kọrí sí Ifẹ̀,
Nígbà tí ó dé Ifẹ̀,
Ajá kò lèè gbó o;
Àkùkọ kò lèè kọ láti mọ̀ ọjọ́;
Àgbò kò kan Ọ̀rúnmìlà.
Ọ̀rúnmìlà wáà bẹ̀rẹ̀ sí í jó,
Ó bẹ̀rẹ̀ sí í yọ̀
Ó ní, Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Ẹ wáà bá ni ní tiṣẹ́gun!

## Ese Èkejo

Àdyà kòrò orí ilẹ̀,
Edun kòrò orí igi ẹmí;
K'ìmọ̀ f'Irù nà mó,
K'ẹ̀mí f'Irù nà ó;
A dá fún Olúkọ̀tún, Ìrẹ̀ dẹdẹ,
Ọmọ Ọ̀rìn ní yàgayàga,
Tí ì ṣe ilé Ifá.
Ní ọjọ́ tí ó ń lọ rèé ṣe ìgbálẹ̀ sí ìkú,
L'òdò Arákùnẹ̀ baba àgbà l'óru Ifẹ̀
Wọ́n ní kí wọn ó mọ̀ lú
L'ọ̀dún mẹ́ta, oṣù mẹ́ta, ọjọ́ mẹ́ta.
Èrò Ìpo,
Èrò Ọ̀fà,
Ẹ wáà bá ni ní tiṣẹ́gun.

### ATÙMỌ̀

1 *Kùbùsùbùsù*: ìrukẹ̀rẹ̀; ìròkẹ̀rẹ̀.
2 *Àgbè*: Ìbà awọn babaláwo kan.
3 *Ọ̀gèdè*: Ìbà awọn babaláwo ọ̀dọ̀ Ìbọ̀lí.
4 *Ìgbì*: Ìbà awọn babaláwo tí a tún ń pè ní *àròkò*.



# 15 Ọ̀SẸ́ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Agada kò tún m'orí ẹni ó rọ̀'un mọ́;
A díá fún Ọlọ́fin,
A l'èsùru orí rìdọ̀.
Ó ní kí a f'igi mọ̀gi,
Kí á lọ̀ gb'ìbùn igi;
Kí á fi ọ̀pẹ̀ na ọ̀pẹ̀,
Kí á lè lọ̀ gb'ìbùn ọ̀pẹ̀.
Rírù ẹbọ ní í gbe ni;
Àìrú kì í gbèèyan;
E wáá bá ni ní tìgẹ́gun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

A kì í fi ipọ̀njú bá babaláwo gbélẹ̀;
A kì í fi ipọ̀njú lé babaláwo lọ ṣòde;
Ẹni tí ó bá fi ipọ̀njú bá babaláwo gbélẹ̀,
Ẹni tí ó bá sì fi ipọ̀njú lé babaláwo ṣòde,
Olúmọrí yóò tẹsẹ̀ bọ giyàn èèrìn;[1]
A díá fún Lápàdé,
Ọmọ òròrò ẹsà,
Tí ó ń fi ọgbọ́n inú pawó;
Tí ìkà ń fi ọgbọ́n inúù ṣe bírí.
Ìkà, bí o bá wọ̀pẹ̀,
O bẹ̀rù awo,
Bí inú bá jó koríko ilẹ̀,
A bẹ̀rù ìgà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Pàpà lọ̀ẹ̀ tẹni;
Òkunrùn lọ̀ẹ̀ torun rẹ̀;

A dìà fún Ọ̀rúnmìlà,
Hà á ń lọ rèé ra Ẹrú Ìjẹ̀rà.
Ẹrú ò lórí à gbẹ́rù lé,
Orí rere ní tèré.
Ẹrú ò mọ̀ mọ́ lórí à gbẹ́rù lé o,
Orí rere ní tèré.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹ́rin

Kí a mọ̀ ajẹ́ ọ̀rọ̀;
Ẹmí [illegible] ní [illegible];
[illegible] tí [illegible],
Tùmí ò rí bọ̀;
Kí bá rí bọ̀;
À bá tí já lábẹ́;
A dìà fún ẹ̀kánkẹ́nírímọ̀ ìrúnmọlẹ̀,
Wọ́n ń lọ rèé bá ìrìnà mulẹ̀.
Ẹrò Ìpo,
Ẹrò Ọ̀fà;
Ẹ wáà bá ni ní àrúṣẹ́gun;
Àrúṣẹ́gun l'àwá wà.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀karùn

Ìgbín rìnìnrì, ìgbín wọ'nú ìgbó;
Ẹ̀rà ṣe gìnìgìnì, wọn a wọ ọ̀dàn;
A dìà fún Ọdẹ
Tí yóò maa dìgbẹ́ òru.
Wọ́n ní ó kilalẹ̀,
Ẹbọ ni kí ó yára ṣe.
Ọdẹ kọ̀, ọdẹ ò rú.
L'ó bá bó ọ̀fà,
Ó bọ́ ọrun,
Ó kọrí sí inú ìgbó.
Ó kiri kiri títí,
Kò rí nǹkan pa.
L'ó bá padà,
Ó kọrí sílé.
Ó ṣe bẹ́ẹ̀ títí.



Fún nǹkan bí ọdún kan,
Kò sì rí ọran pa.
Ó wáà tún mú ọ̀jẹ̀ kàn ọ̀ta,
Ó kọrí sí oko aláwo.
Àwọn babaláwo rẹ̀ ki fún un pé:
Ohun tí Olúígbó bá gbà,
Kí á fi fún Olúígbó;
Ohun tí Olúọ̀dàn bá gbà,
Kí á fi fún Olúọ̀dàn,
Kí á lè bàà ní
Ohun tí a bá fẹ́ ní.
Wọ́n ní kí ọdẹ ó rú
Ìgbín kan, ohun kan àti ẹ̀kùnkù abẹrẹ.
Kí wọ́n ó tọ Ọsẹ̀ Méjì lé ìyẹ̀rosùn lórí,
Kí wọ́n ó dà á sórí ẹbọ náà.
Kí ọdẹ ó lọ gbé e sí ọ̀nà ìgbó àti ọ̀dàn
Ọdẹ sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Nígbà tí ó di alẹ́ ọjọ́ náà
Tí ọdẹ lọ sí ìgbẹ́;
Bí ó ti wọ ìgbó,
Ìgbín l'ó kọ́ rí,
Ó he é,
Ó sọ ọ́ sí àpò.
Ó tún wẹ̀yìn,
Ó rí ahun,
Ó sọ ọ́ sí à [illegible] rẹ̀.
Bí ó ti yà padà,
Tí ó fẹ́ máa lọ,
L'ó bá rí ako àgbọ̀nrín kan.
L'ó bá ta á ní ọfà.
Ó sì pa àgbọ̀nrín náà.
Nígbà tí ó gbé àgbọ̀nrín náà ru,
Tí ó ń lọ sílé,
Ó wáà bẹ̀rẹ̀ sí í yin àwọn awo rẹ̀,
Àwọn awo rẹ̀ ń yin Ifá.
Ó ní, 'Ohun tí Olúígbó bá gbà,
K'á fi fún Olúígbó;
Ohun tí Olúọ̀dàn bá gbà,
K'á fi fún Olúọ̀dàn
Kí á lè bàà ní

Ohun ti a ń ṣe ni
Kéè pé o,
Kéè jinà;
Ẹ wáá bá ni ní àríṣẹ̀gun;
Àríṣẹ̀gun l'àwá wà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Tanàn abẹ́jẹ̀ ṣàkaṛṣàkan;
Gbòngbò ọ̀nà abirin gbàngbìnghìn mọ́lẹ̀.
Ẹ̀rígì ńlá ni í pamọ wọn ní ilú Ṣàkam;
Alákọ̀ọ̀, awọn wọn n'ílé Ọlọ́fin;
A dìá fún ọkọ̀ọ kàn.
Wọ́n ní ẹbọ ni k'ó ó ṣe.
Ahéré ni í ṣawo inú oko;
Òkìtì bàńbà ni í ṣawo ẹ̀bá ọ̀nà.
Ẹmí ni ng ó ò lékèe wọn;
Fìlà ní í lékè orí
Ẹmí ni ng ó ò lékè ọ̀tàá mi.
Àkẹtẹ̀ ní í lékèe Fìlà;
Ẹmí ni ng ó ò lékè ọ̀tàá mi.
Àátàn ni í lékè ilẹ̀;
Ẹmí ni ng ó ò lékè ọ̀tàá mi.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ọ̀sẹ̀ẹ̀rẹ̀ kò gbodọ̀ rìn bí ògòǹgò,
Bí wọ́n bá páwọn ó rìn bí ògòǹgò,
Ẹsẹ̀ wọn ní í máa ṣẹ́.
A dìá fún ẹyẹ Ọlongo
Tí ó ní òun ó bàá Ògòǹgò lọ ìjà.
Bí Ọlongo bá ri Ògòǹgò,
Inúu rẹ̀ a bàjẹ́.
A ní kín ni ó ṣe
Tí òun ó fi tóbi tó Ògòǹgò;
A ní bóyá rírìn
Tí òun ó máa rìn mọ́ ọn ni.



Ọlongo wáá ńrí èèyí bẹ́ẹ̀ẹ,
Ó l'oòko aláwo,
Àwọn awo rẹ̀ ní
Kò ní í leè bá a mu
Kí Ọlongo ó máa bá Ògòǹgò rìn.
Wọ́n ní kò sí ẹbọ
Tí Ọlongo lè ṣe
Tí ó fi lè tóbi tó Ògòǹgò,
Wọ́n ní Ọ̀sẹ̀ẹ̀rẹ̀ kò gbodọ̀ rìn bí ògòǹgò;
Bí ó bá ní pé òun ó rìn bí Ògòǹgò,
Ṣìṣẹ́ ni ẹsẹ̀ rẹ̀ ó ò ṣẹ́,
Kí ẹni yàowọ̀nrìn má ṣe bá
Ẹni tìkàntọ̀kẹ̀ rìn.
Nígbà ti Ọlongo gbọ́ èyí,
Ó ní bí òun ò bá leè tóbi mọ́,
Báwo ni òun ó ti ṣe níyì o?
Àwọn awo rẹ̀ ní kí ó rúbọ.
Ẹbọ kín ni òun ó ba rú báyìí?
Wọ́n ní kí ó rú ẹbọ iyì.
Wọ́n ní kí ó rú aṣọ funfun kìkìkì kan,
Kí ó rú aṣọ ẹtù kan;
Kí ó sì rú aṣọ òdòdó kan.
Ọlongo gbọ́, ó rú,
Ìgbà t'ó rúbọ ńlá tán,
Àwọn awo rẹ̀ ní kó gbé e lọ
Sí idí Ẹ̀ṣù.
Nígbà ti Ẹ̀ṣù gba ẹbọ ńlá tán,
Ẹ̀ṣù wáá dá irú aṣọ ti olongo rú,
Ó ní kí Ọlongo ó máa wọ̀ ọ́,
Ọlongo sì ṣe bẹ́ẹ̀.
Nígbà ti àwọn ẹyẹ yòókù rí olongo,
Ni wọ́n bá ń yọ̀ọ̀ mọ́ ọn.
Wọ́n ní nibo l'ó ti rí
Irú aṣọ dòndàrà bẹ́ẹ̀.
Àwọn ẹyẹ kéékèèké ẹgbẹ́ẹ rẹ̀ a pé,
Wọn a sì máa wo Ọlongo.
Ìdí nìyí ti ó fi jẹ́ wí pé
Bí Ọlongo bá wà nínbìkan,
Àwọn ẹyẹ wẹ́ẹ̀rẹ́ ó máa pé bá á.

## Ese Ẹ̀kẹjọ

Ṣéṣẹ́ ni mo ṣọ;
Awo Ẹtu nínú igbó
Ṣẹ́ṣẹ́ṣẹ́ ni mo rìn;
Awo Òòrẹ̀ ijù.
A dìí fún Ẹtu,
A bù fún Òòrẹ̀.
Nígbà ti àwọn méjèèji
Ó máa lọ rèé gbé inú igbó.
Wọn ní ẹbọ ni wọn ó ṣe.
Wọn ní kí wọn ó rú ẹgbàá owó
Tí a sìn mọ́ ara akèrèngbé;
Kí wọn ó rú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìrawé igbó;
Kí wọn ó sì rú ajere kan.
Ẹtù rú gbogbo ẹbọ náà,
Ṣùgbọ́n Òòrẹ̀ ò rú gbogbo rẹ̀ tán
Ó ti gbéķèlé ipẹ́ ara rẹ̀
Pé ipẹ́ náà ni òun ó máa fi ṣe ọfà.
Tí òun ó maa ta mọ́ àwọn ọ̀tá òun
Ni wọ́n bá múra,
Wọn kọrí sí inú igbó.
Nígbà ti wọ́n dé inú igbó tán,
Ni àwọn ọ̀tá bá ti ó yọ
Lati pa Ẹtu,
Olobo ajere ti ó rú a sọ ọ́.
Ti ó bá sì wọ ibikibi,
Ti àwọn ọ̀tá wá,
Yóò tètè lura,
Yóò sì ri àwọn ọ̀tá rẹ̀.
Bí ó bá ti rí àwọn ọ̀tá rẹ̀,
Yóò tètè sáré.
Bí ó bá sì ti ń sáré,
Ewe rẹ̀ a máa yin Ọ̀sẹ́,
Ewe rẹ̀ a máa dún ṣẹ́ṣẹ́ṣẹ́.
Ṣùgbọ́n bí àwọn ọ̀tá
Bá ti ń lé Òòrẹ̀ lọ,
Òòrẹ̀ a kan orí mọ́lẹ̀,
A wá kukukúkú
A si maa fún ipẹ́ rẹ̀.



Bí ó bá sì ta ipẹ́ sí ọ̀tá,
Dìẹ̀ ìbẹ̀ a bá àwọn ọ̀tá;
Ṣùgbọ́n iyí kò wí pé
Kí wọn ó mọ́ ná ọ̀n ní igi lórí.

### ÀTÙMỌ̀

1. *Ọ̀gẹ́rẹ̀ àkàsà*: inú ilé tóó ti àwọn èèrún á gbé.

# 16 ỌRÀNGÚN MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹkini

Ìgàlà ogun ò ṣeé rí;
Àjàlà ogun kò ṣunwọn;
Bí ogun kò bá di àjàlà tán,
A ò mọ ọkùnrin ní gbẹ̀yìn;
Àlùà[1] pinpin lẹ̀sẹ̀ ọnà;[2]
Olúgbò ò jà wọ́n,
Agana ní í fi í dá wọn lójú ogun.
Èsúrú awo ní Morò;
Àgùtàn, awo Mọ̀rẹ̀rẹ̀;
Ìlàn àgò[1] ní í ṣawo wọn ní Ilé Òyèkè,
Nìbi tí wọ́n gbé ńlọgbọ́n ìmàlè yíraa wọn,
A dífá fún Agana
Tí í ṣe ọmọ Olódùmarè.
Agana ò bá wọn jà
Tó fi ń dá wọn,
Agana ò bá wọn jà,
Tó fi ń dá wọn.

## Ẹsẹ Ẹkeji

Bí ẹsẹ̀ kàn bá ṣíwájú,
Ẹkejì a tẹ̀ lé e;
Bí bàbá bá ṣíwájú;
Ọmọọ rẹ̀ a tẹ̀ lé e;
A dífá fún Àmúrè ò ṣ'ẹ̀gbà,
Tí í ṣe ọmọ bíbí inú Agbọnmìrègún,
Ọ̀rúnmìlà, ò tó kí o wáá bá mi o,
Ẹsẹ̀-kan-ọlá kì í pẹ́ l'ójú ọpọ́n.
Ẹ wo'lé rere,
Ẹ l'àmù wọ̀.
Àmù ò nílé o,



Àmù ò lọ́nà;
Ẹ wo'lé rere,
Ẹ l'àmù wọ̀.

## Ẹsẹ Ẹkẹta

Wọ́n ní kí ì f'aró pakẹ̀;
A f'aró pakẹ̀,
Ìṣalẹ̀ tòn ń jẹ ni.
Wọ́n ní kí ó f'ìtò pajà,
A f'ìtò pa ọjà,
Jẹ̀ńjẹ̀ńjẹ̀ tòn ń jẹ èèyàn.
Wọ́n wáá bí ọkà,
Ọkà ń dìfá.
Wọ́n bá ṣununmọ̀lẹ̀,
Ó ń dìbò,
Wọ́n bá mọ̀ńdámọ̀ńdá,
Ó ń ṣe àrúdà ẹbọ.
A dífá fún Ẹ̀jì Òfún,
Baba ò ṣẹ̀ẹ́gun ọ̀tá dandanndan.
Kèè pẹ́ o,
Kèè jìnà;
Ẹ wáá bá wa ní ìṣẹ́gun.

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Àgì kó, kò dàbọ̀;
Ọgbinghin rin, kò dabọ̀;
Alàkàn ń bẹ n'ilà ibẹ̀ ńgọnn?
A dífá fún Ẹ̀rùbámí,
Tí ó dàgun ìyà àwọn Ùlẹyẹ.
Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó ṣe.
Ẹ̀rùbámí a wáá ṣòwò ìkàrà.
Ìyà àwọn Ùlẹyẹ̀ tọrọ àkàrà,
Ẹ̀rùbámí ò fún un.
Bí ó bá ti di ní alẹ́,
Àwọn ọ̀gbinghin á bẹ̀rẹ̀ sí írin
Ní ẹ̀kùlé Ẹ̀rùbámí gbìnghìnìnghìn.
Nàgbà tí rìnrin àwọn ọ̀gbinghin náà kò,
Tí kò dáwọ̀ dúró mọ́,
Ni Ẹ̀rùbámí bá fi ariwo ta.

O ń kí pé, 'Ẹrú bá mi o, ẹrú bá mi o'.
L'ó bá ti bọ́ kẹ́ dé ilé Ọ̀fún Mẹ́jì.
Ọ̀fún Mẹ́jì ni àkàrà ni kí
Ẹrúbàmí ó lọ fún Ìyá ìwọn Elẹyẹ.
Àti ìgbà t'ó ṣe bẹ́ẹ̀ l'ó tóó ní kómi.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ọmọdé kò l'ojú b'oníkàn Ìkúnú;
Àgbà ò l'ojú b'olú ni ìjẹ̀;
Èni ti ó l'ojú b'odú,
Yóó mọ̀ di awo;
A dífá fún Ọ̀rúngún ilé Ìlá
Tí yóó gbálẹ̀jọ̀ lári òde Ìkìrun.
Wọ́n ní bí ó bá l'ojú b'Ọ̀kọ̀ọ̀,
Orín ni kí ó máa lọ.
A l'ojú b'odú,
A rírè ó;
A l'ojú b'odú,
A rírè
Àwá mọ̀ mọ̀ wáà l'ojú b'odú,
A ó kò mọ̀;
A l'ojú b'odú,
A rírè.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹ̀rìn

Bí ọ̀kẹ́ mẹ́jì bá rìnà wọn,
Wọn a f'ọwọ́ lùwọ́;
Bí àgbẹ̀ mẹ́jì bá rìnà wọn,
Wọn a gbélé,
Wọn a yọ̀;
Bí ìmò mẹ́jì bá rìnà wọn,
Wọn a dìbì ìyèkan;
Ẹni a di à mú mọ̀ ṣọ̀mọ̀ṣọ̀;
Òwú a di àsàbora pínúnù pínúnù;
A dífá fẹ́rì,
Tí ó sùnkún à rí ìkàlẹ̀.
A dífá fún ọrùn,
Wọ́n ó máa bèèrè ọ̀jìgbọ̀n ìlẹ̀kẹ̀.



A dífá fún Ìbàdì ìdí,
Wọ́n ó máa lọ mọ́jàlájì,
Ajẹ ọba t'ó kọ́ná yọ́ọ́rọ́ọ̀yọ́ọ̀rọ́ọ̀.
Orí rúbọ tán,
Orí ń dàbí;
Ọrùn rúbọ tán,
Ọrùn a sì máa lo ọ̀jìgbàrà ìlẹ̀kẹ̀;
Ìbàdì ìdí rúbọ,
Wọ́n ń lọ mọ́jàlájì,
Ajẹ ọba t'ó kọ́ná yọ́ọ́rọ́ọ̀yọ́ọ̀rọ́ọ̀.
Àgbà awo ò ní í fẹsẹ̀ kanlẹ̀,
Orí akọpọ̀n ni kí ó máa bàwo.
Ọ̀pìnmì dé, mi ì lódì,
L'órí akọ ẹsìn.
Awo rere l'Ọ̀rúngún ó ṣe n'Ìlá;
Awo rere.

## Ẹsẹ Ẹ̀karùn-ún

A kì í f'ìtì jó kàrún,
À sì mòù f'ìtìjú bò o;
A dífá fún Àfìnjú,
Tí ó lọ yan ọ̀bùn lálè.
Ẹ̀ríkàndì ọwọ́ pẹ́ẹ̀tẹ̀;
Pẹ́ẹ̀tẹ̀ pẹnrẹ̀ lẹ́sẹ̀.
Bí a ìjìbàn jóbàrìn,
A ó lèé yèrà mọ̀;
A dífá fún Ẹyìn àlọ̀,
Tí yóò mú ọbìnrin rẹ̀ lọ,
N'ilé Àgbọnmìrègún.
Njẹ́, ohùn mọ̀ ó wí o,
Kóóngọ,
Ohùn mọ̀ ó wí o,
Kóóngọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Bí a kò bá bá ọba gbé'lé,
Àbẹ ọba kì í yà ni lórí;
Bí a ò bá bá ọba pàdé,
Ọkọ̀ ọba kì í yà ni lẹ́sẹ̀;

Ìwọ tàù sùré lọ sí kàrin igbó,
O tóó dáko;
A dìí fún Olókun, sẹ̀ní ade,
Ajíf'ilùkì, ọmọ ọba lábùlabù,
Bí igbá ẹyọ.
Rírú ọbọ ni í gbe ni,
Àìrú kì í gbèéyàn;
Kóò pé o,
Kóò jìnà;
Ẹ wáà bá ni ní àrùṣẹ̀gun,
Àrùṣẹ̀gun l'àwá wà.

ATÚMỌ̀

1 *Àlùkì*: ìrìn tí a fi de nókan mọ́lẹ̀ ìrìn rẹ̀ jẹ ọ̀kọ̀ọ̀kọ̀.
2 *mùdè*: *kìnìbì*; ẹni tí a dè mọ́lẹ̀.
3 *Èhu ẹyẹ*: oko ìnu igbó kan tí ó kọ ìlà sí ara, tí ó ń dára púpọ̀; ó gbọ́n púpọ̀ púpọ̀.



# Àlàyé Lórí Ẹsẹ̀ Ifá Kọ̀ọ̀kan

# 1 ÈJÌ OGBÈ

## Ẹsẹ Ẹkini

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ẹdun àti àáyá. Orígì ọ̀bọ kan ni àwọn ẹranko mẹ́jẹ̀ẹ̀jì yìí jùgbọ̀n wọn ó fi kòwọ̀ jẹ ara wọn tó bẹ̃. Ẹranko tí ó ńgbé orí igi ni àwọn mẹ́jẹ̀ẹ̀jì. Bí ẹdun bá kúrò ni orí igi, tí ó bá ti bọ́ sí ilẹ̀ẹ̀lẹ̀, kò lè sáré mọ́. Ni ẹsẹ Ifá náà fi sọ wí pé 'Ará b'ẹ́dun ólẹ̀, ẹdun ò mọ̀ sá. Ará orí igi l'ó yẹ ẹdun.'

Àgbàdo ni ẹdun àti àáyá fẹ́ràn jù láti máa ya jẹ nígbà tí ọ̀dọ́n kò bá tí tó ìtóṣẹ́. Ìtàn yí ó sọ fún wa bí ọ̀wọ́ ṣe tẹ ẹdun ní ọjọ́ kan tí òun àti àáyá lọ ya àgbàdo. Ìwájú àwọn Ògbóni ni wọ́n mú ẹdun lọ nítorí pé àwọn ni ońdàájọ́ ayé àtijọ́. Àwọn Ògbóni kò láti pa ẹdun nítorí pé ọmọ Ọ̀gun ni àti nítorí wí pé ó jẹ́wọ́ pé òun jí àgbàdo ya. Ṣùgbọ́n àwọn Ògbóni pàṣẹ wí pé bí wọn ó ti lọ́pà jẹ àáyà nítorí pé ó ṣe ọ̀dọ́n sá.

Ìtàn yí fi hàn pé ni ayé àtijọ́, àwọn babaa wa a máa fi ìyà jẹ ẹni tí ó bá jalè àti ẹni tí ó bá pàkó. Lóòótọ́ ìtàn náà dá lórí àwọn ẹranko mẹ́jì—ẹdun àti àáyá—ṣùgbọ́n ẹ̀kọ́ pàtàkì ni wọ́n fẹ́ fi ìtàn náà kọ́ wa wí pé olè-jíjà àti èké-ṣíṣe kò dára.

## Ẹsẹ Ẹkeji

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí àwọn ńnkan ìlànà àti àwo mẹ́jì: Ẹ̀gún àti Orò. Ìtàn náà ń sọ fún wa wí pé ìbéji ni Ẹ̀gún. Èyí tán wa lérí pé ẹni tí ó wà l'ilé ẹ̀kú jẹ́ ìránṣẹ́ fún ẹni tí ó ti kú sí ọ̀run tí a sì dá Ẹ̀gún fún. Ẹni tí ó wà lọ́run náà, tí a dá Ẹ̀gún fún láyé dà bí ìbéjì fún àwọn ìpokan ṣẹ tí ó wà láyé. Kò ní í fẹ́ kí wọn ó kú, bẹ̃ ni kò ní í fẹ́ kí wọn ó rùn, yóò sì máa dààbò bò wọ́n. Ìdí níyì tí Ẹ̀gún inú ìtàn náà fi ń sọ fún ìbéjì rẹ̀ tí ó wà láyé wí pé kí ó má tíì wá sí ọ̀run nítorí pé ìbẹ̀ kò 'rọ̀'. Nítorí náà, ẹ̀kú Ẹ̀gún jẹ́ ohun tí ń so àwọn ará ayé àti àwọn ọ̀kú ọ̀run pọ̀ tí wọn sì fi ń dà bí ìbéjì ara wọn. 'Ẹ̀kú ayé o, ẹ̀kú ọ̀run ni à ń pè ní ẹ̀ẹ̀gbẹ́dẹ̀ ẹ̀kú.'

Apá kejì ìtàn náà ń sọ ìtàn mìíràn fún wa nípa bí Ẹ̀gún ṣe gbé ọmọ ìyá Èjì Ogbè lọ ní ọjọ́ kan tí ohùnrin náà ń wá Ìkólé. Nígbà tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í wá ọmọ náà, Ẹ̀gún sọ pé òun kò gbé ọmọ. Orò náà sọ pé òun ò gbé ọmọ. Ṣùgbọ́n ní ìkẹhìn Orò l'ó mú ọmọ náà fún ìyá

Èjì Ogbè. Èyí ñ hàn wá pé nǹkan kan náà ni Eégún àti Orò. Mímọ̀ tí wọn mọ̀ aṣọ náà fún iyá Èjì Ogbè ló sọ Èjì Ogbè di ọrẹ Eégún àti Orò. Ìdí ni èyí tí ó fi jẹ́ wí pé ìtàn àwọn ìbọ mẹ́jẹ̀ẹ̀jì yí ñ máa ñ pọ̀ nínú Odù Èjì Ogbè.

Ẹni tí a bá dá Ifá yìí fún, ó ní láti jẹ́ wí pé wọ́n gbé aṣọ kìí rẹ lọ. Ìlì ó bá le bọ Eégún àti Orò, yóò rí aṣọ náà.

## Ese Èkejì

Ẹsẹ Ifá yí ñ sọ̀rọ̀ nípa ilẹ̀-dídá. Àwọn baba wa kórira ilẹ̀-dídà lọ́pọ̀lọpọ̀. Ọ̀rọ̀ àti iyekan kò gbọdọ̀ da ara wọn nítorí pé irú ìwà burúkú bẹ́ẹ̀ lè fa ikú. Ẹnikẹ́ni tí a ń bá jẹ, tí a ñ bá mu, kò gbọdọ̀ da ni. Ní ayé awọn babańlá wa, wọn gbà gbọ́ wí pé ilẹ̀ ń pa ẹnikẹ́ni tí ó bá da ọmọnìkejì rẹ̀.

Àwọn Yorùbá a máa bá ọ̀rẹ́ mulẹ̀ nítorí kí wọn ó mọ̀ bíà da ara wọn. Wọ́n gbà gbọ́ wí pé ẹni tí a bá bá mulẹ̀, tí a sì da ni, ilẹ̀ ó pa olúwarẹ̀. 'Aṣẹ̀ dọwọ́ ilẹ̀ o jọ mu.'

Àwọn Yorùbá ka ọ̀rẹ́ sí pọ̀pọ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n sì ṣe ka iyekan tàbí ẹbí sí. Bí ọ̀rẹ́ àti iyekan kò bá da ara wọn, gbogbo nǹkan ó máa lọ létòó, a ó sì máa ní ìgbàgbọ́ sí ara wa.

Ẹsẹ Ifá yìí tún ń fi yé wa wí pé àdàkà-ṣìṣe kò dara. Ìwà àdàkàṣìṣe kò sí máa ń pa àwọn ẹrú nítorí pé ẹni fẹ́ràn àti mọ̀ ọ̀fọ̀ọ̀fọ̀ kààkiri. Èpè kò sì dára. Bí ènìyàn bá ñ ifújú ṣépè, ó lè ṣe mọ́ olúwarẹ̀ lára. Àwọn olè fẹ́ràn láti máa tètè ṣépè kí olóhun ó mọ̀ bíà fúnra pé àwọn kò gbé nǹkan tí ó sọnù.

A ṣe àkíyèsí ìwàkúwà tí ó jọ̀jú lóri ilẹ̀ lójọ̀ tití lọ sí ìlà kọ̀ọ̀kọ̀ọ̀gùn. 'A jọ gbóri ilẹ̀, a jẹ . . .' tí a tẹnu mọ́ nǹkan ñ hàn pé ẹnikẹ́ni tí a bá jẹ ñ jẹ, tí a sì jẹ ñ mu lóri ilẹ̀ ayé yìí, kò gbọdọ̀ da ni.

## Ese Èkẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí sọ ìtàn ẹyẹlé fún wá, bí ó ṣe di ẹyẹ ilé àti bí ó ṣe jẹ́ wí pé mẹ́jìmẹ́jì ni ó máa ń bí nígbà gbogbo. Èjì Ogbè l'ó sọ ẹyẹlé di iyá ìbejì nítorí èyí ni babaláwo ñ máa ñ sin ẹyẹlé. Ẹyẹlé jẹ́ ológìn àti ọ̀bọ àwúre pàtàkì nínú ètùtù Ifá. Ìre ni ẹyẹlé máa ñ fà wá nígbà gbogbo.

Ẹsẹ Ifá yìí tún mẹ́nuba fífẹ́ràn ti ẹyẹlé máa ñ fẹ́ràn olówó rẹ̀. Ẹyẹlé fẹ́ràn olówo rẹ̀ dé ibi wí pé tí ilé olówo wọ́n bá ñ jó, wọn kì í kúrò nínú ilé náà, jíjóná ni wọ́n máa ñ bá ilé náà jóná.

Ẹsẹ Ifá yìí ñ sọ àṣọ̀tẹ̀lẹ̀ ire ìbejì fún àgàn kan tí kò rí ọmọ bí. Kí àgàn náà ó lọ di mọ́ Ifá nítorí pé yóò bí ìbejì bí ó bá le rúbọ.



## Ese Èkaàrùn

Ẹsẹ Ifá yìí ñ sọ̀rọ̀ nípa ire ọgbọ́. Ó ṣe fún wa bí Ọ̀rúnmìlà ṣe bá ìkú mulẹ̀ pé kí ó mọ̀ bíà pa òun ní àìkerẹ́. Wọ́n ka ẹbọ fún Ọ̀rúnmìlà, ó sì rúbọ. Díẹ̀ nínú àwọn nǹkan tí Ọ̀rúnmìlà fi rúbọ—agbọ̀ngbọ̀ oríṣè, irin àti èrùpẹ̀ ìlù òkè—jẹ́ nǹkan tí a máa ñ dúnikọ bí a bá ñ sọ̀rọ̀ nípa ire ọgbọ́ àti ire àláàfíà. Igi oṣè a máa gbó kíyẹ́, nǹkan kan kì í ṣe irin, bẹ́ẹ̀ sì ni òkè kì í ku.

Mo dagbàgbọ̀ oríṣè
Ng ò kú mọ́
Mo dìgbà ohè,
Mo kì gbọ́n . . .

Ire ọgbọ́ tàbí ire àláàfíà jẹ́ ire pàtàkì júlọ tí àwọn Yorùbá máa ñ bèèrè fún. Ire mẹ́ta pàtàkì l'ó wà n'ilé ayé—ire owó, ire ọmọ àti ire àìkú parí ìwà. Ire àìkú yìí náà ni à ñ pè ní ire ọgbọ́ tàbí ire àláàfíà.

Ẹsẹ Ifá yìí tún ṣe àlàyé bí ó tí jẹ́ wí pé ó yẹ kí ìgbà awo ó le maa pa ẹnu rẹ̀ mọ́. Kò sí nǹkan tí babaláwo kì í rí. Ṣùgbọ́n ó yẹ kí babaláwo ó lè máa pa ẹnu rẹ̀ mọ́ kí awo ó mọ̀ bíà ya. À fọ̀rọ̀ kè sọ ni pé mẹ́jẹ̀mu pàtàkì ni awọn gbólóhùn yí jẹ fún àwọn babaláwo:

Gbogbo nǹkan ni n ó mọ̀.
Gbogbo nǹkan tí ọrun àti tí ayé
Ní n ó rí,
Ng ó sì máa pa ẹnu mi mọ́.

Apá kejì ẹsẹ Ifá yìí ñ sọ̀rọ̀ nípa ìrìnàjò Ọ̀rúnmìlà sí ìlú kan tí aláàfíà gbé ñ kó aṣọ wọn lọ. Wọ́n wá bí Ọ̀rúnmìlà pé báwo ni àwọn ó ṣe rá nǹkan àwọn. Ọ̀rúnmìlà sì sọ wí pé àwọn ará ọ̀run ló dá aláàfíà náà nílẹ̀. Ó tún sọ fún wọn wí pé àwọn ará ilẹ̀ náà dá ogun ayé àti ogun ajẹ́, èyí l'ó fà á tí wọn ñ rán Orò sí wọn pẹ̀lú aláàfíà. Ó ní:

Aláàfíà ni oníko à á pa Orò,
A ó kè sí Orò,
Aláàfíà ni kí ẹ máa kè sí . . .

## Ese Èkẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí sọ ìtàn bí àwọn ará òde Ìlọ̀ ṣe ní ọba. Nígbà tí àwọn ará ìlú Ìlọ̀ kò ní ọba ni wọn bá lọ dáfá, àwọn babaláwo sì sọ fún wọn pé kí wọn ó rúbọ. Wọ́n rán ñ kúnu pé bí wọ́n bá rí ọba náà

tán, kí wọn ó gbé e lọ sí etíkun, kí wọn ó sì mú ẹnikẹni tí wọn bá rí mbẹ̀, kí wọn ó fi jọba ìlú Ìdó. Nígbà tí àwọn ará ìlú Ìdó ṣe bẹ́ẹ̀ tán ará bẹ̀rẹ̀ sí í rọ̀ wọ́n, wọn sì yin àwọn babaláwo tó dáfá fún wọn, àwọn ará náà sì ń yin Ifá.

A rí àpẹẹrẹ fọ́ọ̀nù nínú ẹsẹ Ifá yìí bíi ìlà kìíní dé ìlà kẹjọ níbi tí a gbé fi 'Kun' ṣeré. Dídún wúrà ọ̀rọ̀ yí ní gbogbo ibi tí a gbé fi ṣeré bu ẹwà kún ọ̀nà tí a ń ṣe ẹsẹ Ifá náà ní ọ̀sọ̀.

### Ẹsẹ Ẹkẹje

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ kìlọ̀kìlọ̀ fún ẹni tí a bá fẹ́ fi jẹ oyè tàbí tí a fẹ́ fi sí ipò agbára kan. Abẹ̀rẹ̀ ni Ọ̀rúnmìlà fi ṣe ìkìlọ̀ náà. Ó ní kí wọn ó wo abẹ́rẹ́ bí ojú àti imú rẹ̀ ṣe mú, ṣùgbọ́n tí ìdí rẹ̀ ṣe ànmú. Ó ní kí wọn ó wo erin, ẹfọ̀n àti jìkùmọ̀ nínú igbó. Ọ̀rúnmìlà ní bí àwọn ẹranko wọ̀nyí ìbá ṣe wí pé bí ó ti wu àwọn ni àwọn ó máa ṣe ni, gbogbo ẹranko ìbá ti tán nígbà. Ọ̀rúnmìlà ní gẹ́gẹ́ bí abẹ́rẹ́ àti àwọn ẹranko inú igbó wọ̀nyí ni kí olórí ó máa ṣe. Olórí kan kò gbọdọ̀ jẹ́ yọ̀pọ̀ tí kò ní ìbikan à á gbáà mú. Olórí kò gbọdọ̀ ṣe bí ó bá ṣe wù ú kí egbé tàbí ìlú náà ó mọ̀ bá bàjẹ́.

Ní ìparí itàn náà, Ifá ní orí l'ó ṣe ọ̀kún dèrùko. Ohun tí Ọ̀rúnmìlà ó wí nihiin ní wí pé orí l'ó ń fi ẹ̀èyàn jẹ ọba,

> Orí tí ó dàdé
> Nínú agọ̀nodẹ ni tí í yọ̀ọ̀ wá.
> Ọrùn tí ó le ọ̀ìgbàlẹ̀kẹ̀
> Nínú agọ̀nodẹ ni tí í yọ̀ọ̀ wá.
> Ìbíbẹ́ẹ̀lì tí ó le màràjì,
> Àgọ̀ ọba t'ó kúná yanranyantan,
> Nínú agọ̀nodẹ ni tí í yọ̀ọ̀ wá.

### Ẹsẹ Ẹkẹjọ

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa ẹni tí ń ṣe rere, ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ wí pé ibi ni àwọn ọmọ aráyé fi ń sú u. Ó wá mú àpẹẹrẹ ìwòlú òpìpùí fún àwa ọmọ ènìyàn. Ó sọ wí pé ẹni tí ó bá mọ̀ ìṣe okùnkùn, kí ó má ṣe dá òpìpùí lóró. Ó tún fi àpẹẹrẹ ògèdẹ̀ tí ó ń ṣe ọmọ lóore mìgìrìgìrì, ṣùgbọ́n tí àwọn àgbẹ̀ máa ń bẹ́ lulẹ̀ bí ó bá ti gbó tán. Ó wáá parí ẹsẹ Ifá náà pẹ̀lú ìkìlọ̀ fún àwọn ìlú tí kì í ro ire sí ohun tí ó wá kí wọn ó tó bá á jẹ́. Ó ní:

> Ohun t'ògèdẹ̀ ṣe l'àgbẹ̀ l'ó pọ̀.
> Ro rere,
> Ikà, ro rere.



# 2 ỌYẸ̀KÚ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹkìní

Ohun tí Ifá ó wí nínú ẹsẹ yìí ni wí pé ẹnikẹ́ni tí ó bá tí bí Ọyẹ̀kú Méjì mulẹ̀, ikú kò lè pa á mọ́. Ẹni tí a bí dá Ọyẹ̀kú Méjì fún, tí ó rúbọ, tí a sì jí ewé Ifá fún, tí bọ̀ lọ́wọ́ ikú. Bí ikú tilẹ̀ ń pa àwọn èèyàn mìíràn, ikú kò ní í pa ẹni tí ó tí bí Ọyẹ̀kú Méjì mulẹ̀ nítorí pé:

> Gbogbo àlàwẹ́ obì ni ikú ń pa,
> Ọ̀rọ̀ ni ó ń pa oòrùn obì sì.

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa ọ̀rọ̀ ìlẹ̀-mímu àti ìlẹ̀-dídà. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ń bá ọ̀rọ̀ ẹni mulẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni a ṣe ń bá ìkàn ẹni (Ifá ẹni tàbí òrìṣà mìíràn tí à ń sìn) mulẹ̀. Nítorí ìgbà tí a bá sì ti rúbọ, tí a sì ṣe gbogbo ètùtù tí ó yẹ, òrìṣà tí a ń bọ kò gbọdọ̀ da 'ni.

Ẹsẹ Ifá náà tún sọ̀rọ̀ nípa ìmú-bíbí àti ẹ̀dọ̀-fífọ̀. Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ wí pé ìmú-bíbí ni àbíjà kò dára. A kò sì gbọdọ̀ fi ìbínú ení hàn sí ẹni tí ó ju ni lọ. Bí ẹnu bá fa ìbínú yọ sí olówó rẹ̀ ikú ni iyà àjẹmọ́yà l'ó fi ń ṣere. 'Imú ń b'ẹ́winrẹ̀, ó ń f'ẹsẹ̀ janlẹ̀, yóò p'olówó ẹ̀ jẹ bí?'

Nínú ìparí ẹsẹ Ifá náà, a tí wúrà ọ̀rọ̀ kan nínú oríkì Odù yí ṣeré láti fún tẹ̀mmọ́ ọ̀rọ̀ nípa wí pé ikú tí yẹ̀ lórí ẹni tí ó ń sìn Ifá. Wúrà ọ̀rọ̀ náà ni 'yẹ̀' tí í ṣe alábà kan láti 'Ọyẹ̀kú', oríkì Odù yí. Ó ní:

> 'Kú mọ̀ pawo mọ́ o,
> Ikú tí yẹ̀ lórí awo.

### Ẹsẹ Ẹkẹta

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí àbìkàní tí ó bọ fún ẹni tí ó bá rúbọ. Ọlọ́mọ Akátá ni ó ṣamọ̀nà lọ sí ìlú gbìgìdá gbọnlọ ni wọ́n bá ní kí ó rúbọ. Oríkọ àwọn babaláwo tí ó dá Ifá náà ni:

> Bí a bá yọ̀,
> Èmí ó yọ̀.
> Yangí ilé, wọn ọ̀ gbọdọ̀ yọ̀lẹ̀.
> Àtàrì, wọn ọ̀ gbọdọ̀ yẹ èmí ọ̀gà.

Oríkọ̀ àwọn babaláwo yìí ntí tún ń sọ irú ohun tí ẹsẹ̀ kìíní Odù yìí sọ: ẹni tí ó bá tẹjúmọ́ Ọ̀yẹ̀kú Méjì, Ifá kò ní í yẹ̀ lẹ́dọ̀ olúwarẹ̀.

Nígbà tí Ọlọmọ Akotó rúbọ tán, tí wọn ṣe Ifá fún un, l'ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í lájé. Ó wá ń sọ fún ajé pé kí ó ya'lé òun wá kí ó wá jẹun.

Nínú ẹsẹ̀ Ifá yìí, a tún rí i bí a ṣe fi 'yẹ̀' ṣerè nínú oríkọ̀ àwọn babaláwo tí ó dá Ifá náà. Oríṣìí ìfọ̀rọ̀ṣeré tí a máa ń rí lò nínú oríkọ̀ Odù tí ẹsẹ̀ náà tí jáde wá ni èyí. Ìrúfẹ̀ ìfọ̀rọ̀ṣeré bẹ́ẹ̀ pọ̀ nínú ẹsẹ̀ Ifá, ó sì máa ń tèté fi ìmọ̀ Odù tí a ti mu ẹsẹ̀ Ifá oríṣìí bẹ́ẹ̀ hàn.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹta

Ọ̀rọ̀ nípa ogbó ni ẹsẹ̀ Ifá yìí tún ń sọ. Ẹsẹ̀ Ifá yìí kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ nípa Ọlọ́fin àkọ́kọ́ tí à á pè ní Odùduwà ẹni tí ó gbó púpọ̀ láyé. Òun ni wọ́n ń kì ní:

> Ọlọ́fin orúgbó
> Ọlọ́fin baakaawóó,
> Ọlọ́fin tí wọn l'áwọn ó fi l'édù oyè,
> T'ó gbó gbóó gbó,
> T'ó sì dọ́ta mọ́ wọn lọ́wọ́.

Ẹsẹ̀ Ifá náà wá ń ṣe ìlérí fún ẹni tí ó dá Ọ̀yẹ̀kú Méjì pé yóò gbóó láyé. Pẹ̀lú jùlọ, ẹsẹ̀ Ifá náà ń ṣe ìdánilójú fún àwọn babaláwo tí ń sin Ifá lójú méjèèjì ni pé:

> Ẹ rìnrin l'ẹ̀dún nígbà,
> Ẹ ó sì tún rìnrin lẹ́ẹ̀mí o.

Ẹsẹ̀ yìí wá ṣe ìdánilójú ọ̀rọ̀ ogbó yìí fún babaláwo tí ń sin Ifá dé ibi wí pé irú èèyàn bẹ́ẹ̀ dà bí ẹyẹ igbó tí ń sin Olódùmarè tí ó sì jẹ́ wí pé ó máa ń pẹ́ láyé. O tún wáá sọ pé ikú àti àrùn kò lè ṣe babaláwo náà ní ìkankan nítorí pé ó dà bí ẹyẹ igbó tí ó pẹ́ láyé tí wọ́n sì fi jẹ olúwo láàyéran.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ̀ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa ọmọ-bíbí. Ó ń fi bí adìẹ òkòkò ṣe ń bímọ ṣe àpẹẹrẹ. Bí adìẹ bá yé lílí pẹ́ẹ̀, òkòkò fi ń bímọ tiẹ̀ láàgbàjà. Bákan náà ni ẹni tí ó ń sin Ọ̀yẹ̀kú Méjì ó ṣe bí ọmọ tiẹ̀ láìní ìyọnu.

Nínú apá kejì ẹsẹ̀ yìí, Ifá wá ń sọ wí pé ọmọ-bíbí ni èrè ìbàgbépọ̀ ọkọ àti aya. Bẹ́ẹ̀ sì ni bí ọkọlayà kò bá sún mọ́ ara wọn, wọn kò lè rí ọmọ bí. Ifá wá parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ nínú ẹsẹ̀ yìí pẹ̀lú pípè àpẹẹrẹ oyin tí ó ń bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ tí ó sì ń fún un ní ìníhàní àti ṣe òró tí ó ń mú inú rẹ̀ dùn. Bí ó ti jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ kì í bu ilé oyin jẹ́, tí ọmọ púpọ̀ ń mú ilé oyin dùn, bẹ́ẹ̀ náà ni adùn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ní láti wà nílé ọlọ́mọ.

Ọ̀yẹ̀lẹ̀ àti òkòkò tí a lò ní ìhín jẹ́ oríkì fún adìẹ. Bí adìẹ ṣe máa ń pe ọmọ rẹ̀ ni a fi ń pè é ní òkòkò. Ilẹ̀ tí adìẹ sì máa ń yẹ̀ nígbà gbogbo ni a fi ń pè é ní 'Ọ̀yẹ̀lẹ̀'.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀karùn

Apá kìíní ẹsẹ̀ Ifá yìí sọ nípa ìpò tí Ọ̀yẹ̀kú Méjì kó nínú orí òkè-yẹ̀yẹ̀. Ọ̀yẹ̀kú Méjì ló kọ́ àwọn ọmọ aráyé bí a ṣe ń ya òkú ẹni.

Apá kejì wá sọ wí pé gẹ́gẹ́ bí ẹnikan kì í ṣeé fi ìyà jẹ ọrọ àti aránṣọ̀ọ̀rí pé ọmọ Òòṣà ni wọ́n, bẹ́ẹ̀ náà ni ẹnìkẹ́ni kò le gbọ́dọ̀ fi ìyà jẹ ọmọ Ifá.

> Mo mọ̀ dọmọ ọ̀pẹ̀ yẹ̀kẹ́tẹ̀
> Kẹ́nìkẹ́ni mọ̀ mọ̀ ṣe ná mí o.

Ẹsẹ̀ Ifá náà tún sọ aláìjù pé ẹni to bá na ọmọ Ifá ní ìnì rìjà Ifá.

> Ẹni t'ó bá ná mi,
> A rìjà baba mi . . . ;
> Ẹni ó nỌ̀yẹ̀kú a r'ìjà Ògbè.

Ìṣẹ̀ṣẹ púpọ̀ ni ẹsẹ̀ Ifá yìí jẹ́ fún àwọn oníṣẹ̀ṣẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọmọ Ifá rìnnà títí t'ó fi dé ìlú Ọ̀pọ̀ntẹ́gẹ̀rẹ̀, ẹ̀nìkan kan kò gbọ́dọ̀ ṣe é. Gbogbo ibi ní láti máa yà lọ́nà fún ọ̀pẹ̀ yẹ̀kẹ́tẹ̀ ni. Idí rèyí tí a fi parí ẹsẹ̀ Ifá náà pẹ̀lú:

> Ẹ yà lọ́nà
> Ẹ jẹ́ n lọ.

## Ẹsẹ̀ Ẹ̀kẹfà

Ọ̀rọ̀ nípa ìre ogbó ni ẹsẹ̀ Ifá yìí ń sọ. Ẹsẹ̀ Ifá náà bẹ̀rẹ̀ ìròhìn ìrìn-àjò babaláwo kan lọ sí òde Ọ̀pá-ìlàkàká níbi tí ó gbé bá wọn tí wọn pa aláhaḿan àti òòrẹ̀, tí wọn sì ń fi ọpọ́n aláhaḿan dá alun, tí wọn tún ń fi ìpẹ́ òòrẹ̀ dá àúrẹ̀. Nínú ìtàn yìí, aláhaḿan àti òòrẹ̀ dúró fún àwọn ọ̀kẹ́gbẹ́n ayé àti alágbára tí ikú ń pa ní òde Ọ̀pá-ìlàkàká.

Ẹsẹ̀ Ifá náà tún wáá ṣe àkíyèsí wí pé bí ọdún bá dun tán, gbogbo ewéko ni í máa ń wọ́wé. Ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá jẹ́ ọmọ Ọ̀yẹ̀kú kò

gbọdọ̀ bá wọn kó ikú àjọkú nítorí pé ọmọ Ọ̀yẹ̀kú ti di 'Àgbàdìwọ̀n-rùn' bí Olófin àkọ́kọ́. Àwọn òrìṣà tí fọ̀ ọ̀ funfun, wọ́n ti sì é jinrú. Nítorí náà ọmọ Ọ̀yẹ̀kú nìkan gbọ́ kí ó sì dà bí irin lílọ̀. Bí ikú tilẹ̀ ó pa ọ̀pọ̀ ènìyàn, tí ó ń pa ẹlẹ́bahun pẹ̀lú ọ̀pọ̀n, tí ó ń pa òtọ̀ tìpẹ̀tìpẹ̀, tí gbogbo ewéko ń wọ̀wé lọ́ọ̀ọ̀dún, ọmọ Ọ̀yẹ̀kú kò ní í bá wọn kú ikú àjọkú.

> Àgbàdìrin ni mo mọ̀ mọ̀ dà.
> Kí ng mọ̀ mọ̀ bá wọn kúkú àjọkú o.
> Àgbàdìwọ̀nrùn ni mo mọ̀ dà.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Ẹsẹ Ifá yìí ó sọ nípa bí Ọ̀yẹ̀kú Méjì ṣe di Ọ̀yẹ̀kú. Ìtàn ni ẹsẹ náà ó sọ nípa ìlú kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Pópó. Nínú ìlú yìí ni Ọ̀yẹ̀kú gbé kọ́ àwọn ọmọ aráyé bí wọn ó ṣe máa ya ọkọ̀ wọn. Àwọn ẹyẹ t'ó bá Ọ̀yẹ̀kú ya àwọn ọkọ̀ ìlú Pópó náà ni igún, àkàlà àti tẹ̀ntẹ̀rẹ́. Ọ̀yẹ̀kú sọ fún àwọn ará ìlú Pópó pé kí wọn ó kó àwọn ọkọ̀ wọn wá sí ìgbèlé ìlú náà. Níbẹ̀ ni tẹ̀ntẹ̀rẹ́ ti fi pàṣán méje ya àwọn ọkọ̀ náà.

Nínú ẹsẹ Ifá yìí, a tún rí ìpò tí Ọ̀yẹ̀kú kó nípa orò òkùyíyà. Láti ìgbà náà ni àwọn ọmọ aráyé ti sọ Ọ̀yẹ̀kú di Ọ̀yẹ̀kú.

Wọ́n dárúkọ pàṣán nílùlú gẹ́gẹ́ bí ohun èlò òkú-yíyà. Títí di òníolónìí pàṣán ni a máa ń fi í rolẹ̀ nígbà tí a bá ń pe òkú tí a fẹ́ yà. Ìdí níyí tí àwọn egúngún fi máa ń mú pàṣán lọ́wọ́.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹsàn-án

Ẹsẹ Ifá yìí ń ṣe àlàyé ipò pàtàkì tí orí kó nínú àwọn ìbọ ilẹ̀ Yorùbá. Ẹsẹ náà dá lórí babaláwo kan tí ó fẹ́ ní ire gbogbo, tí ó wá lọ fi ọ̀rọ̀ sun Ọ̀rúnmìlà wí pé 'gbogbo ire gbogbo ni òun ó wá'. Ọ̀rúnmìlà ní kí akápò ó lọ sọ fún Èṣù ẹni tí í ṣe alágbe fún gbogbo àwọn òrìṣà. Nígbà tí babaláwo náà dé ọ̀dọ̀ Èṣù, ó sọ fún un pé gbogbo ohun tí ó dùn babaláwo náà kó dun Ifá. Èṣù wá gba akápò náà ní ìmọ̀ràn wí pé kí ó lọ ní gbogbo ohun t'ó ń fẹ́ fún orí rẹ̀. Nígbà tí akápò ṣe bẹ́ẹ̀ tán ni gbogbo nǹkan tí ó fẹ́ bẹ̀rẹ̀ wá tẹ̀ ẹ́ lọ́wọ́. Ó wá ń jó, ó ń yọ̀, ó ní:

> Ǹjẹ́, ohun gbogbo t'ó bá ń dùn mí,
> Ng ó máa rò f'órí mi.
> Orí ẹni ni alágbàwìndùn.
> Orí mi là mí o,
> Ìrọ̀ bàlágbàwìndùn.



Ohun tí ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ni pé kò sí òrìṣà t'ó le dá ni gbè lẹ́yìn orí ẹni. Nítorí náà, ohunkóhun t'ó ń dùn wá, a nílati kọ́ fi lọ orí ẹni, kí orí ẹni ó fi ọwọ́ sí i, kí ó tó di wí pé àwọn òrìṣà ṣe nǹkan náà fún un. Orí onikálùkú ni òrìṣà rẹ̀ tí kò le dà á, tí ó sì ń gba ọ̀rọ̀n rẹ̀ yẹ̀wò. Ìdí níyí tí ẹsẹ Ifá nílùlu fi sọ wí pé:

> Orí pẹ̀lẹ́,
> Àtètè níran.
> Àtètè gbe ni kòòṣà.
> Kò sóòṣà tí í dá ni í gbè
> Lẹ́yìn orí ẹni.

## 3 ÌWÒRÌ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹ̀kínní

Ẹsẹ Ifá yìí ó ṣe àlàyé pé ìlàgbọ̀ràn kò dára. Ó fi àdán tí wọ́n sọ fún pé k'ó má jẹ ẹ̀wọ̀ igi ẹmi ní ọ̀sìngangan ṣe àpẹẹrẹ. Wọ́n sọ fún àdán pé ẹ̀wọ̀ ẹmi tí àwọn ọmọ aráyé ń jẹ kò jọ ẹ̀wọ̀ ìrókò tí àwọn ọmọ aráyé kì í jẹ. Wọ́n tún ṣe àlàyé fún àdán pé b'ó bá dé'bi ẹ̀wọ̀ ẹmi ní ọ̀sìngangan, ẹlẹ́mì ó fi kànnàkànnà pa á. Àdán ò gbọ́. Ó lọ sí ibi ẹ̀wọ̀ ẹmi ní ọ̀sìngangan, nígbà tí ẹlẹ́mì rí i, ó sì fi kànnàkànnà pa á.

Ohun tí Ifá ń wí nílùlu ni pé ìgọràn wá fún ẹnikẹ́ni tí àwọn babaláwo bá kì ilọ̀ fún, ṣùgbọ́n tí kò gbọ́. Àdán a máa jẹ ẹ̀wọ̀ igi ẹmi àti igi ìrókò, ṣùgbọ́n àdán kò gbọdọ̀ dé ibi igi ẹmi ní ọ̀sìngangan. Bí ó bá ṣèbẹ̀, àwọn ọmọ aráyé lè pa á. Bákan náà, ẹni tí a bá ka òòrọ̀ fún tí ò gbọ́, ohun búburú ni ojú rẹ̀ ó rí ní ìkẹ́hìn.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Nǹkan pàtàkì méjì ni Ifá ń wí nínú ẹsẹ yìí. Lọ́nà kìní, Ifá ń sọ pé ìpín tàbí orí onikálùkú nǹkan l'ó le gbè é. Bí òòṣà kan tilẹ̀ fẹ́ gbe ènìyàn, tí orí olúwarẹ̀ kò bá lọ́wọ́ sí i, kò ní í ṣeé ṣe. Nígbà tí akápò lọ fi ẹjọ́ Ọ̀rúnmìlà sùn lọ́dọ̀ Olódùmarè, ni Ifá wá sọ fún Olódùmarè pé òun ni gbogbo ìpò òun fún akápò, ṣùgbọ́n ìpín akápò ni kò gbà. Èyí fi yé wa wí pé orí ẹni l'ó máa ń tọrọ nǹkan fún ni lọ́wọ́ Olódùmarè. Ohunkóhun tí orí ẹni ò bá fẹ́, ọwọ́ ẹni kò lè tó nǹkan náà.

Apá kejì ẹsẹ Ifá yìí ń sọ wí pé kò yẹ kí ènìyàn ó máa dá ẹjọ́ ẹ̀kún kan. Nígbà tí Olódùmarè gbọ́ ti ẹnu akápò tán, ó ránṣẹ́ sí Ọ̀rúnmìlà pé kí òun náà ó wá sọ ti ẹnu rẹ̀. Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà ro ẹjọ́ tirẹ̀ kalẹ̀ tán ni ọ̀rọ̀ náà wá yé Olódùmarè yékéyéké, ó sì rí ìdí rẹ̀ tí Ọ̀rúnmìlà kò fi gbe akápò rẹ̀. Láti ọjọ́ náà ni Olódùmarè ti pa àṣẹ pé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ dá ẹjọ́ ẹ̀kún kan. Ó ní:

Àníkàndájọ́, o ò ṣeun.
Àníkàndájọ́, o ò ṣèèyàn.
Nígbà tí o ò gbọ́ t'ẹnu ẹnìkejì,
Ẹni l'o dájọ́ ṣe.

A tún rí ọ̀rọ̀ pàtàkì kan nínú orúkọ àwọn babaláwo tó dá Ifá yìí. Nínú orúkọ yìí ni a ti ń kọ́ wa wí pé kò yẹ kí àgbà ó máa kọ iṣẹ́ fún ẹwe. Ní ẹ̀rọ̀, àgbà l'ó yẹ kí ó máa rán ọmọdé níṣẹ́. Ṣùgbọ́n bí ọmọdé bá bẹ àgbà ní iṣẹ́ tí agbára ọmọdé náà ò ká, ó yẹ kí àgbà ó jẹ́ iṣẹ́ náà nítorí pé 'gbogbo wa l'a ńṣe a jọ ń bẹ'ra wa'.

Èyí fi hàn wí pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé ọmọdé l'ó nílò̩ ìtọ́jú fún àgbà, tí yóò sì máa yẹ àgbà sí nígbà gbogbo, síbẹ̀síbẹ̀ àgbà náà nílàti mún nǹkan láti ṣe nǹkan tí ó bá yẹ fún ọmọdé.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ìtàn nípa bí Olódùmarè ṣe dá ilẹ̀ ayé ni ẹsẹ Ifá yìí ó tọ́ka sí. Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé adìẹ àti ẹyẹlé pẹ̀lú erùpẹ̀ inú agbọ̀n ni Olódùmarè fún àwọn irúnmọlẹ̀ l'ó rọ̀ sílẹ̀ ní Ilẹ̀ Oòduyè tí àwọn irúnmọlẹ̀ náà fi ṣe ọ̀nà ilọ̀ẹ̀. Kò sí ilẹ̀ nígbà náà, ìgbẹ́dẹ́ omi ni gbogbo ilẹ̀ ayé. Erùpẹ̀ inú agbọ̀n yìí ni adìẹ àti ẹyẹlé náà tàn kálákiri Ilẹ̀ Oòduyè tí gbogbo ayé fi di ìtẹ́ẹ̀rẹ̀ báyìí. Irúnmọlẹ̀ tí ó ṣe ìdótò tí a fi dá ilẹ̀ yìí ni Odùduwà ẹni tí í ṣe Ọlọ́fin àkọ́kọ́.

Ìdí níyí tí adìẹ àti ẹyẹlé fi ṣe pàtàkì nínú ẹbọ Ifá. Ẹsẹ Ifá yìí ó ṣe àlàyé nípa ìwúlò adìẹ nípa títú nǹkan wò. Ẹyẹlé kò lè tan ilẹ̀ dáadáa bí adìẹ. Nítorí náà bí ọ̀rọ̀ bá dijú, àwọn Yorùbá a máa sọ wí pé 'ẹyẹlé ní ó tàn án, adìẹ kò i dé'bẹ̀'. Èyí ni ìtumọ̀ ìlà kẹta àti ìkẹrin ẹwì yìí tí ó sọ pé:

A dìá fún òkòkò níyẹ̀lẹ̀
Tí yóò bá ni tùlẹ̀ yí wò.

Àwọn babaláwo fẹ́ràn láti máa fi adìẹ rúbọ sí àwọn irúnmọlẹ̀ nítorí pé adìẹ a máa fà, wọ́n sì gbà gbọ́ pé bí wọ́n bá fi rúbọ yóò lùkà àwọn kò ìkò ìsì ìrún lọ. Gẹ́gẹ́ bí orin Ifá kan ṣe wí:



Àgbébọ̀ adìẹ,
Ṣára yẹ̀yẹ̀ gbọnkú lọ o.
Ṣára yẹ̀yẹ̀.

Nítorí ipò pàtàkì tí adìẹ kó nínú ẹbọ rírú ni ẹsẹ Ifá yìí fi sọ wí pé:

Kín ni ó làá ni tùnlẹ̀ yí ṣe?
Òkòkò níyẹ̀lẹ̀
Ni yóò bá ni tùnlẹ̀ yí ṣe.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí sọ ìtàn nípa Ògún, òrìṣà tí a gbà gbọ́ pé ó dá ọdẹ-ṣíṣe sílẹ̀. Nínú ìtàn náà, Ògún ń lọ sí ìgbẹ́ ọdẹ l'ó bá lọ dáfá lọ́dọ̀ àwọn awo rẹ̀ tí orúkọ wọn ń jẹ́:

Ará ilé lóólú,
Mo dá lójú,
Mo fi dé ẹnu;
Mo ṣe àgbọ̀n lóńlẹ̀ wọ̀rì wọ̀rì.

Àwọn babaláwo yìí ka ẹbọ fún Ògún. Wọ́n ní k'ó ní aṣọ dúdú kan, bùjé dìẹ̀, ìpẹ̀pẹ̀ irin, màrìwo ọ̀pẹ̀ àti ewé ilá lọ́kọ̀. Ògún sì rú gbogbo ẹbọ náà. Wọ́n ní kí Ògún ó gbé ẹbọ náà lọ sí àlà oko nibi tí àgbọ̀nrín gbé ń jẹ. Níbẹ̀ ni Ògún gbé pa ìkàmọ̀ gidi kan. Inú Ògún dùn tó bẹ́ẹ̀ tí ó bẹ̀rẹ̀ sí í fi ìwo orí ìgalà náà tí ó ń pè ní ekutu àti atan (nibi tí ó gbe yan ẹran náà) ṣe ìgo. Ògún wá ń ṣe ara rẹ̀ ní ọnìbùjé nítorí pé ó ti fi bùjé rúbọ.

Bí a bá kíyè sí ẹbọ tí Ògún rú, a ó rí i pé nǹkan dúdú l'ó pọ̀ jù níbẹ̀. Bóyá nítorí pé ènìyàn dúdú fafa ni Ògún pàápàá ni ẹbọ nǹkan dúdú orí̩ṣàìríṣà fi tọ̀ sí i. Ọ̀kan nínú ìdìun tí Ògún fi rúbọ ni ìpẹ̀pẹ̀ irin tí í ṣe àmì kan pàtàkì fún òòṣà yí.

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ìtàn Ògún àti ọdẹ-ṣíṣe. Títí di òní-olónìí, bí àwọn ọdẹ bá ń lọ sí ìgbó ọdẹ, wọ́n ní láti kọ́kọ́ dífá, kí wọn ó sì ta ẹbọ dànù kí wọn ó tó lọ. Ògún tí í ṣe òrìṣà àwọn ọdẹ l'ó kọ́kọ́ fi àṣà yí lélẹ̀.

### Ẹsẹ Ẹ̀karùn

Ẹsẹ Ifá yìí náà ń sọ̀rọ̀ nípa ìgbèrùn sí àwọn babaláwo lẹ́nu. Wọ́n kìlọ̀ fún Ọ̀fìnrìn Ọ̀kígà pé kí ó má ṣe lọ dẹ igbó Ìwòrì ní ìgàngan-gan, ṣùgbọ́n kò gbọ́. Bí ó ṣe wọ'nú igbó Ìwòrì ni àwọn ìrin bí

di kíjìpá kan wáàkà hìhun bò ó lórí. Kíjìpá ẹbọ Ìwòrì tí Ọ̀fínrán Ọ̀kọ̀jà ó rú náà ni ó gbé e kiri dòní olóníì tí ó ń pé ni àwọ̀ ẹ̀kùn.

Ẹsẹ Ifá yìí ń ṣe àlàyé pé ẹni tí kò bá rúbọ, tí kò sì gbọ́ràn sí àwọn babaláwo lẹ́nu tí wọ́n ara rẹ̀ di ìjẹ fún àwọn ajogun. Ẹgà ati àwọn ìránmọlẹ̀ yòókù kò ni í sí lẹ́hìn ìrú àkíyàn bẹ́ẹ̀ nítorí pé 'ẹni ó rúbọ ni Ẹ̀ṣù gbè'. Nítorí náà àwọn ajogun tábí ẹbọra lè fi olóoríyẹ̀ dá ara ti wọ́n bá fẹ́.

Apá kẹ́ta ẹsẹ Ifá yìí ṣe àlàyé ní ṣókí nípa ìhùwàsí àwọn ẹranko àti ẹyẹ oríṣiríṣi. Ó ní aláàrìn kò dúró de ojú tàbí ẹnu kí ó tó kọ́ ilé tirẹ̀. Èyí jẹ́ àkíyèsí pàtàkì nítorí pé tọ̀jọ̀-tẹ̀ẹ̀rùn ilé aláàrìn kì í gbẹ. Ifá tún ṣe àlàyé bí àfèbọ̀jọ̀ ṣe máa ń wa ìsà tirẹ̀. Àfèbọ̀jọ̀ tí a tún ń pè ní eku jẹ́ ẹranko tíi kan tí ó tóbi tó àgbà ewúrẹ́ tí ó máa ń gbẹ́ ìsà rẹ̀. Ẹranko yìí a máa wa ìsà tirẹ̀ jinlẹ̀ gìdìgbì, bẹ́ẹ̀ ni ìsà náà a máa tóbi lọ́pọ̀lọpọ̀. Ìdí nìyí tí ẹsẹ Ifá yìí fi sọ wí pé:

> Àfèbọ̀jọ̀ ní í walẹ̀ tiẹ̀ wìndìnrin wìndìnrin wìndìnrin.
> Ilé àfèbọ̀jọ̀ gbọ́ọ̀rọ̀, ó gbòòrò,
> Bẹ́ẹ̀ ni kò gbọdọ̀ jọbà.

Ẹsẹ Ifá yìí tún wá mẹ́nubà eku kékeré bí ẹmọ́ tàbí ẹ̀lìrí tí ó máa ń wa ìràn sí ojú-ilé tirẹ̀ nítorí tí ó gbé máa ń sọ kúlú kùlú. Ẹsẹ Ifá náà tún sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀gà tí ó máa ń dorí ilé tirẹ̀ kodò kòdòdò. Gbogbo àwọn àkíyèsí wọ̀nyí l'ó bá ìgbésí àwọn ẹranko àti ẹyẹ wọ̀nyí mu régírégí.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ní àkọ́kọ́, àpèjúwe ni ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ fún Ọ̀rúnmìlà ẹni tí a tún máa ń pè ní Ẹlà. Ifá mẹ́nu àkọ́kọ́ ti sọ bí Ẹlà ṣe jẹ́ afinjú ènìyàn tí ó mọ́ fínnífínní. Lẹ́hìn èyí àpèjúwe ni ẹsẹ Ifá yìí tí ré mọ́ ìtàn Ọ̀kànbí, ọmọ Odùduwà tí wọ́n fi jẹ ọba ilé baba rẹ̀, tí wọ́n sì ṣe ìlérí fún wí pé ire ajé àti ire ọmọ ó tọ̀ ọ́ lọ́wọ́; tí ó sì rí bẹ́ẹ̀ fún un lẹ́yìn tí ó rúbọ tán.

Ìpari ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ sí ìrírí àti ìgbẹ́kẹ̀lé pàtàkì. Babaláwo tí ń ki Ifá yìí ń ṣe ìlérí pé bí Ifá bá le jẹ́ kí ire ajé ó tọ̀ òun lọ́wọ́, òun ó máa fi gbogbo ìfẹ́ọ̀kan òun mọ̀wọ̀ọ́wọ́ àti ìkàrí òun pọ̀ọ̀ sin Ọ̀rúnmìlà. Ó tún wá ń wúre pé kí Ọ̀rúnmìlà ó jẹ́ kí òun ó ru òun gbo, kí òun ó ru òun tó.

Ohun tí Ifá ń sọ nìhìín ni pé ẹ̀gbẹ́ bí Ọ̀kànbí tí a kọ́kọ́ dá ẹsẹ Ifá yìí fún ṣe di olówó àti ọlọ́mọ, bẹ́ẹ̀ náà gan-an ní ó rí fún ẹni tí a dá ẹsẹ Ifá yìí fún bí ó bá le rúbọ. Ṣùgbọ́n bí ó bá rí bẹ́ẹ̀ tán fún



ọmọbìnrin tí a dá Ifá yìí fún, òun náà nílátí máa fi gbogbo ọgbọ́n rẹ̀ sin Ifá kí ó lè baà tún ṣe ori rere nípa ire ọgbọ́n àti ire ẹyẹ tí ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú gbogbo ire.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹje

Ifá ń sọ fún wa nìhìín pé Ìwòrì Mẹ́jì l'ó kọ́ alágbẹ̀dẹ wí pé kí wọ́n ó máa fi ọwọ́ bọ́ ojú alápò kí wọ́n ó máa fọ̀ ọ́ ní alágbà gbogbo. Títí di òní, àwọn alágbẹ̀dẹ kì í fẹ́ fi ọwọ́ wọn tàbí kí wọ́n ó wọ̀ ìtì tí wọ́n ó fi parí iṣẹ́ wọn lálẹ́. Wọ́n ń ṣe èyí nítorí pé wọ́n nílátí wá ni àlà irin tí wọ́n bá ń rọ nígbà gbogbo, kí irin náà ó mọ̀ baà jónà.

Ìtumọ̀ ìtàn yìí ni wí pé Ìwòrì Mẹ́jì mọ̀ nípa àṣírí irin rírọ. Ìdí nìyí tí ọ̀rọ̀ nípa Ògún àti nípa arọ̀-ṣíṣe fi pọ̀ nínú Odù yí. Ìwòrì ni babaláwo alágbẹ̀dẹ àkọ́kọ́ ní ilé Ìmàgùn. Nítorí náà àwọn alágbẹ̀dẹ nílátí tújú Odù yí nítorí ìsere tí ó ṣe wọ́n nípa kíkọ́ wọn ní iṣẹ́ arọ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Ọ̀rọ̀ nípa ìgbọràn àti ẹbọ-rírú ni ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ lé. Àìrúbọ l'ó fà á t'ó fi jẹ́ pé bí òdè bá kún tán, ṣùgbọ́n bí ó bá di ọ̀gànjọ́, ó nílátí dá wàì nítorí pé gbogbo èèyàn ó ti kúrò lódè, wọ́n ó ti mọ ilé wọn lọ. Láìsítọ́, ó ń yẹ òde ni ìrọ̀lẹ́ títí di ọwọ́ alẹ́, ṣùgbọ́n àìrúbọ kò jẹ kí ẹyẹ náà ó lè kalẹ̀:

> Òdè kún, òde ó kún tán;
> Ìrọ̀lẹ́ òdè jọ, kò jọ jìnà.

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí gidi nípa ohun t'ó ń ṣẹlẹ̀ lójúde lójoojúmọ́. Àwọn èèyàn dúdú lẹ́hìn kíti máa gbà atẹ́gùn lójúde wa láti ìrọ̀lẹ́ títí di ọwọ́ alẹ́. Ṣùgbọ́n bí kò bá jẹ́ wí pé a ń ṣe ìnáwó tàbí àṣeyọ kan b'ó bá ti di ọ̀gànjọ́, gbogbo èèyàn nílátí túká wọnú ilé lọ. Ifá wá mú àkíyèsí ohun tí a mọ̀ dájúdájú yìí láti fi ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn tí kì í fẹ́ rúbọ wí pé ìmọ̀ wọn kò lè jọ jìnà nítorí pé:

> Kírú ẹbọ ni í gbe ni,
> Àìrú kì í gbèèyàn . . .

# 4 ÒDÍ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Ẹsẹ Ifá yìí sọ ìtàn bí Òdí ṣe wọnú lọ sí ìlú Òkò tí ó sì rí ìrè orísìírísìí níbẹ̀. Ẹsẹ Ifá yìí wá ń ṣe ìkìlọ̀ fún ẹni tí ó dá Òdí Méjì pé bákan náà ni ó máa gbé ojú kan rí ire gbogbo. Ẹsẹ Ifá náà wá la àpẹẹrẹ iyọ̀ l'ó jẹ́ wí pé ojú kan náà ti a bá fi sí l'ó máa ń wà títí tí yóò fi domi. Ó tún la àpẹẹrẹ òkè tí kì í kúrò lójú kan náà tí ó fi máa ń gba ẹ̀bọ tirẹ̀. Ó wá ní bákan náà ni onibééré yìí ó ṣe máa gbé ojú kan náà rí're gbogbo.

Àwọn pàtàkì ni ẹsẹ Ifá yìí jà sí. Àwítúnwí ìlà méjì wọnyí:

> Ire gbogbo dá wá o,
> Igìrìrì igìrìrì.

tún ńkan ìṣẹ Ifá mọ́lẹ̀ nípa dídá tí onibééré fẹ́ kí ire gbogbo ó máa fi agbára Ifá dá wá sí ọ̀dọ̀ òun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtumọ̀ tí Èṣù kò fi gbọdọ̀ jẹ àdí. Àdí ni orúkọ iyọ̀ tó wo Èṣù dìgbà ń jẹ́. Ìyá náà a sì máa gbé àrọ̀sìn. Ṣùgbọ́n ọ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ ni, èkùrọ́ kì í ṣe àrọ̀sìn. Èṣù l'ó ṣe é tí èkùrọ́ fi ń ṣe àrọ̀sìn nígbà tí ó bá pan án. Nígbà tí ó sì ti jẹ́ pé òwò àrọ̀sìn yí ni ìyá Èṣù ń ṣe, ni gbogbo èèyàn bá fi ń pe àrọ̀sìn èkùrọ́ ní àdí.

Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé Èṣù kò gbọdọ̀ fẹnu kan àdí, ṣùgbọ́n ó fẹ́ràn epo. Ẹni tí ó bá fún Èṣù ní àdí jẹ ni láti ri ìjà òrìṣà yí. Bí èèyàn bá sì fẹ́ kí Èṣù ó bá ẹnìkan jà, ohunrẹ̀ lè ta àdí dà sí orí Èṣù kí ó sì wí pé onítọ̀hún l'ó rán òun láti fún Èṣù ní àdí jẹ. Kíá ni Èṣù ó bá ẹni tí a dárúkọ rẹ̀ jà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ohun tí Ifá ń wí nínú ni pé bí ẹni tí a dá Òdí Méjì fún bá rúbọ tí wọn kà ọ̀fẹ̀ fún un, dandan ni kí ó rí ire ajé, ire ọmọ àti ire ìlú yorí ìwà. Ó wá ṣe àlàyé wí pé bẹ́ẹ̀ ni Òdí ṣe ṣe fún Alárá, Ọlọ́fin àti Ọ̀wárángún-àgà. Bẹ́ẹ̀ náà ni yóò sì ṣe fún ẹnikẹ́ni tí ó bá rúbọ tí ó sì ní ìgbọ́kànlé nínú Òdí Méjì lẹ́yìn tí a bá ti dá Ifá tán, tí Odù yìí sì yọ sí olùwarẹ̀.



Orin Ifá tí ó parí ẹsẹ yìí ń fi ogbó ẹni tí ó rúbọ Òdí Méjì wé ogbó àti ara-àlè Èṣù ẹni tí nǹkan kì í ṣe nígbà kan kan. Ó ní:

> Ng la bẹ́ẹ̀ṣù o ò,
> Kangiri.
> Àìkú la bẹ́ẹ̀ṣù o ò,
> Kangiri.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn bí àwọn ará Ifẹ̀ ṣe gba ara wọn lọ́wọ́ ìsìnrú ọba Aláàfin Ọ̀yọ́. Òdí Méjì l'ó kọ́ àwọn ará Ifẹ̀ pé kí wọn ó pàrokò ránṣẹ́ sí Aláàfin. Nígbà tí wọn gbé àrokò náà dé Ọ̀yọ́, ọba Aláàfin ní kí wọn ó ránṣẹ́ sí Ọ̀sá tí í ṣe babaláwo Aláàfin. Ọ̀sá l'ó wá túmọ̀ àrokò náà. Ìtàn náà sọ fún wa wí pé láti ọjọ́ náà ni Aláàfin ó ti yọ àwọn ará Ifẹ̀ lọ́wọ́ iṣẹ́ ìsìnrú tí wọ́n ń ṣe ní òde Ọ̀yọ́.

Ìtàn sọ fún wa pé Òdí Méjì jẹ́ pàtàkì ní Ifẹ̀, ó sì ṣe wọ́n ní oore orísìírísìí. Òdí yìí náà ni ìgbà àwọn awo tí í máa ń dífá fún Ọlọ́fin. Ìdí níyí tí a fi ń pe Òdí ní:

> Òdí, àgbàlagbà Ifẹ̀,
> Awo ilé Ọlọ́fin.

## Ẹsẹ Ẹ̀karùn-ún

Nínú ẹsẹ Ifá yìí, a rí ìtàn kan nípa Jàkùta ẹni tí a gbà pé òun ni Àrẹ̀mọ Ọba Ṣàngó, Aláàfin Ọ̀yọ́. Àwọn èèyàn ó lépa Jàkùta, wọ́n sì fẹ́ pa á, ṣùgbọ́n kò ṣeé ṣe. Àwítúnwí àwọn ẹyọ ìlà láti ìlà kejìlá títí dé òkèjọ fi hàn bí inú ọtẹ̀ tí wọ́n dì mọ́ Jàkùta náà ti le tó. Ojoojúmọ́ ni wọ́n ń fẹ́ pa Jàkùta, ṣùgbọ́n ẹnu ìsàsùn ni wọ́n fi ń pa á.

Ọjọ́ tí àwọn Onìṣàngó máa ń bọ Ṣàngó ni ọjọ́ karùn-ún kàrùn-ún ni a ń pè ní ọjọ́ Jàkùta lóde-òní. Ní ọjọ́ náà àwọn onìṣàngó ní láti fi ewé tàbí ọ̀pẹ̀ẹ̀yọ palẹ̀. Wọ́n níláti ro àmàlà fún Ṣàngó kí wọn ó sì ṣe ọbẹ̀ gbẹ̀gìrì sí i. Wọ́n a tún máa pe Ṣàngó ní ọjọ́ náà. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, wọ́n a máa lu Bàtá, tí wọn ó sì jó ijó Ṣàngó pẹ̀lú.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ohun tí Ifá ń wí nínú ẹsẹ yìí ni pé Òdí ni owó lọ́wọ́ tí ó le fún ẹnikẹ́ni tí ó bá wá á. Owó Òdí kì í ṣe owó kékeré. Owó tí ó ń hùn inú ọkẹ́ bàmùbàmù ni ọ̀gẹ̀ẹ̀ bí ataare tí kì í di ẹrù tẹ̀ lẹ́hìn ọkẹ́.

Ó wá dárúkọ àwọn nǹkan èèwọ̀ ẹsẹ Ifá yìí—igba atare, igba ẹyọ owó àti igba ọkà bàbà. Ní ìparí ẹsẹ náà, ó wá sọ pé nínú ọ̀n igba tí ẹ̀ẹ̀rẹ̀ tí jẹ́ ẹbọ fún Ṣàngó, dandan ni kí ẹni tí a dá ẹsẹ Ifá yìí fún ó di ohùn pẹ̀lú ìṣe Ifá tí ó máa ń ṣe wéréwéré tí kì í sí í sọ́.

## Ẹsẹ Èkeje

Ẹsẹ Ifá yìí sọ nípa ìwúlò ọtí fún máa la iyè èèyàn. Nígbà kan rí, Ọ̀rúnmìlà kì í mu ọtí bàbà, bẹ́ẹ̀ ni kì í mu ti ṣẹ̀kẹ̀ṣẹ̀. Àyọrísí rẹ̀ ni pé Ifá kò níyè nínú mọ́. Ṣùgbọ́n nígbà tí Ọ̀rúnmìlà gba igbá ọtí kan pé́rẹ́, wáà ni ìyè rẹ̀ là. Ifá kò lòdì sí ọtí mímu, àmupara nìkan ni kò fẹ́. Ẹsẹ Ifá kan nínú àwọn ọmọ Odù tilẹ̀ ń sọ fún wa wí pé 'ọtí ni ìmúmúgùn ọ̀ni'.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ifá kò lòdì sí ọtí mímu, ohun tí ó ṣe kókó nínú ẹsẹ Ifá tí ó ń sọ fún wa pé ìwọ̀ntunwọ̀nsì ni gbogbo nǹkan dára mọ́. A kò rí àpẹẹrẹ kan nínú ẹsẹ Ifá, níbi tí Ọ̀rúnmìlà ti mu àmupara ọtí tàbí tí ó ti ṣe ìṣẹ̀jú ohunkóhun.

## Ẹsẹ Èkejọ

Nínú ẹsẹ Ifá yìí, Ọ̀rúnmìlà ń sọ pé nǹkan t'ó bá ń dun ẹni tí ó ń ṣe òrìṣà kan l'ó ní lílọ dun òrìṣà náà. Ìtumọ̀ èyí ni pé àwọn òrìṣà wà ẹ̀gẹ́ẹ́ bí olùgbèjàndùn fún àwa ẹdá. Àwọn ni a nílátí máa fi ọ̀rọ̀ wa lọ nígbà gbogbo, àwọn náà kò sì ní í ṣàìdá wa lóhùn.

Ẹsẹ Ifá yìí tún sọ ìtàn kan nípa bí Ọ̀rúnmìlà ṣe fẹ́ obìnrin méjì tí ọ̀kan jẹ́ arẹwà tí èkejì sì jẹ́ ọmọ ọ̀ba. Bákan náà ni a lè sọ pé Ifá ń ìre obìnrin fún ẹnikẹ́ni tí a dá ẹsẹ Ifá yìí fún. Ohun tí ń dun oníwàdìí náà ni ọ̀rọ̀ ìdílómìn. Ifá sọ wí pe òun ó ṣe ìre obìnrin fún un. Obìnrin méjì ni olúwarẹ̀ ó rí lẹ́ẹ̀kan náà, ọ̀kan jẹ́ arẹwà èèyàn, ọ̀kan sì jẹ́ ọmọ ọba. Kí onibéèrè náà ó rúbọ kí ó lè bá rí ire tí ń wá náà.

# 5 ÌROSÙN MÉJÌ

## Ẹsẹ Èkíní

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa ìre ọmọ. Ó sọ ìtàn ẹnìkan tí ń wá ọmọ tò wá lọ dúró sí badè. Ní ibi t'ó dúró sí yìí náà l'ó ti di ọ̀kẹ́mọ. Bákan náà



ni kí ẹni tí a dá Ifá yìí fún ó dúró sí ibi tí ó wà nítorí pé nǹkan rẹ̀ ó ti bímọ.

Ẹsẹ Ifá yìí tún ń sọ̀rọ̀ nípa aṣọ àkìrì àti òdòdó. Aṣọ yìí gbayì púpọ̀. Ifá ń sọ wí pé tiri lẹ́ ni àwọn ìwọ̀ méjèèjì yí ó máa níyì.

A dìá fún Iyé ọlọ́mọ
Àkìrì àti òdòdó
Tí wọn ń lọ s'ẹ́yé ìbílẹ̀ . . .

Nítorí náà, ẹsẹ Ifá yìí tún ń sọ̀rọ̀ nípa ìre àìkú àti ìre iyì. Ẹni tí a dá Ifá yìí fún ó níyì, yóò sì ṣe ọ̀nì gígùn, bí ó bá le rúbọ.

## Ẹsẹ Èkejì

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn ẹnìkan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Yàwọ̀pa ní ìlú Ìrẹ́sì. Yàwọ̀pa jẹ́ ẹni tí ó yàm púpọ̀, tí ara rẹ̀ ó sì balẹ̀ tí bẹ́ẹ̀. Wọ́n sọ fún un pé kò tètè pa ohì, bí wọn ó fi bọ ìrìṣà, ṣùgbọ́n ọrun l'ó yára pa. Ìtumọ̀ ìtàn yìí ni pé ń yẹ kí èèyàn ó máa fimbalẹ̀ gbọ́ ohun tí àwọn babaláwo bá wí kí olúwarẹ̀ ó mọ̀ bá ṣe ìṣẹ̀ṣe.

Nínú orúkọ babaláwo inú ẹsẹ Ifá yìí, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa ìlù tí à ń pè ní Àràn tí àwọn babaláwo máa ń lù. Ìlù yìí jẹ́ ìlù kan pàtàkì fún Ifá. Òun náà ni a tún ń pè ní ìpèsè. Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ fún wa bí ìlù yìí ṣe máa ń dún nígbà tí àwọn ọmọ awo bá gbé àràn balẹ̀ wọn jàde, tí wọn ń lù ú. 'Fìnringingin fìnringingin' àti 'fìnringingin fìnringingin' jẹ́ àkànṣe ohùn tí ìlù àràn máa ń lọ nígbà tí àwọn ọmọlé bá ń lù ú.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ọ̀rọ̀ nípa àbámọ̀ ni ẹsẹ Ifá yìí ń sọ. Ẹsẹ Ifá náà ń ṣe àlàyé pé àìrúbọ l'ó máa ń fa àbámọ̀. Ó tún wá mẹ́nuba ìtàn Ọ̀kànì ilé àti olùgbó. Ìtàn yí sọ fún wa pé Ọ̀kànì ilé l'ó fi olùgbó jayé. Nígbà tí olùgbó d'árí oyè tán, l'ó bá bẹ̀rẹ̀ sí í pa ọmọ Ọ̀kànì jẹ. Ọ̀kànì wá bẹ̀rẹ̀ sí í kọ àbámọ̀, ṣùgbọ́n ọ̀pá kò bóni mọ́.

Àbámọ̀ l'ó máa ń gbẹ̀yìn ọ̀ràn fún ẹni tí kò rúbọ. Kí èèyàn ó mọ̀ bá kàbámọ̀, ó yẹ kí ó rúbọ tí àwọn babaláwo bá kà fún un nítorí pé wàrà wàrà ni ohun tí Ifá wí máa ń ṣẹ:

Ifá dé, àlàṣẹ,
Ọ̀pẹ̀, àlàṣẹ wàrà.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ohun tí Ifá ń wí níhìín ni pé àwìíjẹ kò dára. Aláwìíjẹ náà ni ẹni tí a pè ní ẹlẹ́ri sowere. Ifá ń sọ wí pé ó yẹ kí ènìyàn ó máa gbéjáà sí àwọn àgbà lọ́rùn. Ifá wáá sọ ìtàn ẹrú Ọ̀rúnmìlà kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Tarasenilàígbọ́ tàbí Tarasenílójú. Wọ́n kìlọ̀ fún ẹrú Ọ̀rúnmìlà yí, ṣùgbọ́n kò gbọ́. Nítorí̀ náà, àwìíjẹ sọ. Tarasenílójú di ẹni tí ń gbé inú igbó. Ifá wá sọ wí pé ẹrú Ọ̀rúnmìlà ni ọ̀bọ. Èyí ni pé ènìyàn ni ọ̀bọ tẹ́lẹ̀ rí, ẹrú Ọ̀rúnmìlà sì ni. Àwìígbọ́ l'ó sọ ọ̀bọ di ẹranko tí ń gbé inú igbó.

Ifá sọ ìtàn yí láti fi yé wa pé àwìígbọ́ kò dára. Ìgbẹ̀yìn irú iwà bẹ́ẹ̀ kì í dára nítorí pé ó máa ń sọ ẹni tí ń hu irú iwà bẹ́ẹ̀ di ìlàkọ̀ṣẹ̀ ni. Àrà àwìígbọ́ náà ni àìróbọ. Nínú ìtàn yí, Tarasenílójú kò ríbọ. Ó kọrí ìgbẹ́yin sí ìbọ.

> Àṣẹhinwá, àṣẹhìnbọ̀,
> Tarasenílójú wọ̀gbẹ̀.
> Wọ́n ń ṣe bí ajàkọ̀ kiri
> Mámọ̀ k'ó tóó mọ̀ jẹ́ pé Tarasenílójú ni ìnàkí
> Mámọ̀ k'ó tóó mọ̀ jẹ́ pé Tarasenílójú ni ọ̀bọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀kàrùn

Ọ̀rúnmìlà ń sọ nínú ẹsẹ Ifá yìí pé ẹnikẹ́ni t'ó bá ń tún ti ọmọnikejì ṣe, òun gan-an ni òun ó bàá irú ènìyàn bẹ́ẹ̀ tún tirẹ̀ náà ṣe. Nínú ẹsẹ Ifá yìí, a sọ ìtàn ẹnìkan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Opálìkí tí ó fẹ́ràn láti máa tún ti ọmọnikeji rẹ̀ ṣe jù bí ó ṣe ń tún ti ara rẹ̀ gan-an ṣe lọ. Nítorí̀ náà, Opálìkí náà di ẹni tí ó ní ẹ̀pẹ̀lẹ̀pẹ̀ ọmọlẹ. Nígbà tí inú rẹ̀ dùn tán, ó wí bẹ́ẹ̀ sí i kọrin ọ̀wọ̀. Ó ní:

> Kín ni ó bàá mi túnwàá tèmi ṣe?
> Ọ̀rúnmìlà Baba mi, Ẹ̀rìgì Àlọ̀,
> Ni yóò bá mi túnwàá tèmi ṣe.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Nínú ẹsẹ Ifá yìí, Ọ̀rúnmìlà ń pitàn ogun Ìgbànnokò Ẹ̀kìgì ti Ògún lọ. Ogun yìí jẹ́ èyí tí ẹ̀pẹ̀ ẹsẹ Ifá náà ń dárúkọ. Ogunlile ni ogun Ìgbànnokò Ẹ̀kìgì. Ṣùgbọ́n kí Ògún ó tó lọ sí ogun náà, ó bèèrè lọ́wọ́ àwọn babaláwo, ó sì rúbọ. Ìgbà t'ó rúbọ tán,



> Ó ṣẹ́gun sí ọ̀tún,
> Ó ṣẹ́gun sí òsì,
> Ó bí àwọn ọ̀tá àdẹ̀ láàrin . . .

Ohun tí Ifá ń sọ níhìín ni pé bí o tí wù kí nǹkan ó le tó, ẹni tí ó bá rúbọ, tí ó sì gbọ́ràn sí Ifá lẹ́nu kò ní í pàí lẹ́kẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa ewu tí ó wà nínú àìrúbọ. Ìyá Ìdèrè ni àwọn babaláwo ka ẹbọ fún nígbà tí ó fi ń wá ọmọ. Ṣùgbọ́n kò rú ẹbọ náà. Ó bímọ, ṣùgbọ́n ìpọ́njú kò jẹ́ kí àwọn ọmọ náà ó gbádùn. Ifá ní:

> Bírú ẹbọ ni í gbe 'ni.
> Àìrú kì í gbèèyàn.
> Kéè pé o,
> Kéè jìnà.
> Ẹ wáá wa fi owó kí,
> B'ó tí ń ṣe.

Ìtumọ̀ ẹsẹ yìí ni pé àìrúbọ kò dá ènìyàn dúró láti rí ohun tí ènìyàn ń fẹ́ nígbà míràn. Ṣùgbọ́n bí ènìyàn bá rí ohun tí ó ń wá tán, ó lè jẹ́ wí pé ìgbà náà ni ìyọnu ó tóó dé lórí nǹkan tí ènìyàn ti ń wá náà. Ìyá Ìdèrè bá bímọ lóòótọ́, ṣùgbọ́n ìpọ́njú ni àwọn ọmọ rẹ̀ fi ń ṣayé.

Nínú ọ̀mìkọ̀ àwọn babaláwo tí ó dá Ifá yìí, a rí àpẹẹrẹ ìbìyèsí nípa ẹ̀dá. Ó ní bí ojà bá fẹ́ wọ ìlú, gbẹ́rẹ́gbẹ́rẹ́ l'ó ti ń wọ ọ́. Ó tún sọ nípa orin pé b'ó bá fẹ́ wọ̀lú a máa kígbe kìkankikan, yóò sì fi gbogbo ara rìn lọ́nà tí ó fi hàn pé ohùn tóbi àti agbára ẹranko ni. Gbogbo àkíyèsí wọ̀nyí l'ó lọ láàrà, tí ó sì jọ ohun tí a jíìwe rẹ̀ náà tìmọ́tìmọ́. Èyí fi hàn wí pé àkíyèsí ni Ifá.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Ẹsẹ Ifá yìí ń pitàn kan nípa ilẹ̀ àwọn Tápà. Ẹsẹ Ifá náà dá lórí ẹnìkan tí ilẹ̀ Fítólú ní Ẹ̀kpe tí í ṣe ìlú àwọn Tápà. Fítólú bèèrè lọ́wọ́ àwọn awo rẹ̀ bí ọ̀kẹ̀ àwọn ará ìlú Ẹ̀kpe ṣe lè máa yé ara wọn. Wọ́n ka ẹbọ fún àwọn ará ìlú Ẹ̀kpe, wọ́n sì tún kìlọ̀ fún wọn pé kí wọ́n ó fi ilẹ̀ ògùnì kan báyìí sílẹ̀ kí ẹnikẹ́ni ó má lò ó mọ̀ kí àwọn àwọn ará ìlú náà ó lè bàá ṣàkan. Nígbà tí wọ́n ṣe bẹ́ẹ̀ tán, tí àkó-àìyeṣẹ̀

ó sì lààrin wọn mọ́, wọ́n wá bẹ̀rẹ̀ sí í jà, wọ́n ń yọ̀, wọ́n ń yin àwọn babaláwo; àwọn babaláwo náà ń yin Ifá. Wọ́n ní:

Ọ̀pẹ̀ ń fọ Tápà,
Ẹ ò gbọ́ ni.
Ẹdú mọ̀ mọ̀ ń fọ Tápà,
Ẹ ò gbọ́ ni.

Ohun tí ó pa Ifá pọ̀ mọ́ àwọn Tápà kò kéré. Àwọn kan tilẹ̀ ń sọ pé láti ilẹ̀ àwọn Tápà ni Ifá ti wá sí ilẹ̀ Yorùbá. Tìtí di òní ni àwọn Tápà máa ń dá Ifá ní ìlú wọn. Ifá ṣe wá lààrin àwọn Yorùbá l'ó wà lààrin àwọn Tápà àti àwọn Ẹ̀gún.

Oríkọ̀ àwọn babaláwo tí ó dá Ifá yìí ń tọ́ka sí bẹ̀rẹ̀ tí a fi í kọ́ ilé ní ayé àtijọ́. Kòsíkù kan ni bẹ̀rẹ̀ jẹ́, ṣùgbọ́n bí a bá fi kọ́lé, a máa mú ilé tutù dáadáa. Bẹ̀rẹ̀ yìí náà ni ọba Aláàfin ń máa ń kọ ààfin rẹ̀. Láyé ọjọ́un ni àwọn ìlú t'ó jẹ́ àwọ̀nà fún Ọ̀yọ́ máa ń mú bẹ̀rẹ̀ wá fún Aláàfin láti tún ààfin rẹ̀ ṣe. Àkókò tí wọn máa ń ṣe èyí ni à ń pè ní àkókò ọdún Bẹ̀rẹ̀.

Oríkọ̀ àwọn babaláwo yìí kan náà tún sọ̀rọ̀ bó àkókò tí i sẹ̀ ọ̀dẹ̀dẹ̀ ọ̀là kan tí ó máa ń wà nínú ilé ọ̀là. Nínú àkókò ni àwọn ìgbà ìwo tí màa ń ṣawo.

# 6 ÒWỌ́NRÍN MÉJÌ

## Ese Ẹ̀kíní

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa òjò. Ó kọ́ bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àlàyé òjò nígbà tí ó bá bẹ̀rẹ̀ bẹ̀rẹ̀. Bí òjò ìlú ṣe máa ń kán lu ara ewéko tàbí òrùlé ni èyí tí ó pè ní 'akitipá, akitipá, akitipá' nínú ẹsẹ Ifá yìí. Lẹ́hin ìgbà díẹ̀ tí òjò ìlú bẹ̀rẹ̀ bá ti bẹ̀rẹ̀ sí í kán, á wá bẹ̀rẹ̀ sí í máa rọ̀ gìdìgbà. Ariwo tí òjò ńlá t'ó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí í rọ̀ ni ẹsẹ Ifá yìí ń tọ́ka sí nígbà tí ó wí pé 'ìwọ̀ sísì, ìwọ̀ sísì'. Nígbà tí ó bá tún yá, òjò ìlú náà ó bẹ̀rẹ̀ sí í la àgbàrá. Àgbàrá òjò náà l'ó pè ní 'àwọ̀ọ̀dá àkumọ, àwọ̀ọ̀dá àkumọ'. Lẹ́hin ìgbà pípẹ́ tí òjò náà ti ń rọ̀, yóò bẹ̀rẹ̀ sí í máa rọ̀ díẹ̀, díẹ̀ díẹ̀ díẹ̀ tí ó fi jẹ́ wí pé kíkàn tí ó ti bẹ̀rẹ̀ lákọ̀ọ́kọ́ ni ó fi parí. Irú èyí ni ẹsẹ Ifá yìí pè ní 'Ọ̀wààrà, òwọ̀ ṣíṣísí, ọ̀wààrà òwọ̀ ṣíṣísí'. Irú òjò tí ó rọ̀ díẹ̀, tí ń kán díẹ̀ báyìí, kì í tètè dá. Èyí l'ó fà á tí ẹsẹ Ifá yìí fi wí pé:

Bí wọn bá ń rọ̀,
Wọn kì í dá.
Ẹ̀jì a ya sílẹ̀,
Ẹ̀jì a ya ọ̀kun;
Abàtà rọ̀gọ̀dọ̀ a sì dodo.

Ẹsẹ Ifá náà wá parí pẹ̀lú ìjọ̀ nípa Olókun àti Olúgri. Ó ní ọ̀kàn omi kòtòkòtò báyìí ni ọmọ Olókun; ìgbà òjò tí ó wọ̀ àgbàrá l'ó sì ń mú kí odò ńlá ó kún. Olókun ni ìríṣà tí ó ṣe ìtọ́jú òkun, ṣùgbọ́n Olúgri ni ó ṣe ìtọ́jú odò ńlá orílẹ̀-èdè.

Ẹsẹ Ifá yìí ń àkíyèsí àwọn baba wa hàn nípa bí òjò ṣe ń rọ̀, bí àgbàrá ṣe ń dé tí ó sì ń di odò àti òkun.

## Ese Ẹ̀kejì

Ìtàn ogun kan tí Òwọ́nrín Méjì lọ ni ẹsẹ Ifá yìí ń sọ. Ogun náà ni à ń pè ní ogun Tìmtọ̀sín. Kí Òwọ́nrín, ẹni tí a tún ń pè ní Òwọ̀n, ó tó lọ sí ogun yìí, ó rúbọ àjàlà, ó sì ní ìgìgun:

Ó ja ogun náà ní àjàlà,
Ó ja ogun náà ní àjànẹ́rù
Ó mú ẹkimin,
Ó sì mú ohinrin.
Ó ṣẹ́gun sínsìjó,
Ó ṣẹ́gun ẹ̀hin,
Ó sì fi ọ̀tá lulẹ̀ kùrin.

Wọ́n wá parí ẹsẹ Ifá náà pẹ̀lú orin Ifá tí ó sọ wí pé Òwọ̀n (tí à ń pè ní Òwọ́nrín) mú ẹrú méjì. Nítorí tí ó ti mú ẹrú méjì yìí ni a ti ń pè é ní Òwọ́nrín Méjì.

Ìtumọ̀ ẹsẹ Ifá yìí fún ẹni tí a dá a fún ni pé bí Òwọ́nrín ṣe ja ogun àjàlà àti àjànẹ́rù bẹ́ẹ̀ gan-an ni ẹnìyìí ó ṣe ní ìṣẹ́gun nípa nǹkan ìlú kan tí ó dàmọ̀lẹ̀. Ifá ní òun ń wo ìṣẹ́gun fún ẹnìyìí o. Ifá ní òun kò ní í jẹ́ kí ojú ó tì í o. Ifá ní bí ó bá le rúbọ, yóò ṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀. Kí enikẹ́ni náà ó má ṣe bẹ̀rù nítorí pé Òwọ́nrín Méjì ó ba a ṣẹ́gun.

## Ese Ẹ̀kẹta

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn nípa ìwọ̀fà kan tí ó di olówó nípa ọ̀lẹ̀ rẹ̀ kan tí ó kó sínú ìgò tí ọba fẹ́ kó lé láti fi ṣe ètùtù lẹ́ ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo tí ó bí ó lé bàà yè. Ìwọ̀fà yí a máa jẹ́ Molẹ̀ọ̀ní, olówó rẹ̀ a sì máa jẹ́

Kiitẹ́ẹ̀ni. Nígbà tí àwọn ọmọ ọba bí Kiitẹ́ẹ̀ni pé tí ló ni òkú adìẹ náà, ó yára dá wọn lóhùn pé òun kọ́ o nítorí pé ó ṣe bí wọ́n fẹ́ mú ẹni tí ó ni òkú adìẹ náà ni. Ṣùgbọ́n nígbà tí àwọn ọmọ ọba fi ojú kan Mọ́ẹ̀ẹ́ni ni wọ́n tó wá jẹ́wọ́ pé àwọn fẹ́ ra adìẹ náà ni; wọ́n sì fún un ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó. Báyìí ni Mọ́ẹ̀ẹ́ni ṣe di ọlọ́rọ̀, tí ó di olówó.

Ẹkọ́ ni ẹsẹ Ifá yìí ń kọ́ wa wí pé kò yẹ kí a máa ro ọmọkọ̀ni pin, kò sì tọ́ kí a máa fi ìyà jẹ ọmọkọ̀ni tí ó bá jẹ́ ọmọ-ọdọ̀ ẹni nítorí pé àwọn irúnmọlẹ̀ lè ṣọ irú ẹni bẹ́ẹ̀ di ẹ̀ẹ̀yàn pàtàkì láìròtẹ́lẹ̀ ní ọ̀nà ẹ̀bùrú. Ifá ń ṣe kìlọ̀kìlọ̀ fún àwọn olówó, ọlọ́rọ̀ àti onípò ọ̀tìsíríṣẹ́ pé kí wọ́n ó ma ṣe lo ipò wọn ní ọ̀nà ìkà àti ọ̀nà ọ̀dàjú nítorí pé kòkòrò ayé kò sí lọ́wọ́ ẹnikan.

Ifá sì tún ń sọ ọ̀rọ̀ ìtùnú fún àwọn tí wọ́n wà ní ipò tí kò dára tàbí ipò wàhálà àti ìpọ́njú. Ifá ń sọ pé kí wọn ó máa fi orí tì í nítorí pé ọ̀nà ẹ̀bùrú ni Irún ó gbà sọ wọn di ẹ̀ẹ̀yàn ààtà bí wọn kò bá gbọ̀nrí nibi ipò búburú náà tí wọn sì ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú òun. Ifá sọ wí pé ojú pọ́n ẹni tí a dá Ọ̀wàsìn Méjì fún, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ rẹ̀ ó di ayọ̀ ní ìkẹhìn bí ó bá le fi orí tì í.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ọfọ̀ Ifá ni ẹsẹ yìí jẹ. Ọfọ̀ ìmúrírun ni. Ifá pe ìmúrírun ní orúkọ tí í jẹ́ nínú ẹsẹ yìí. Ìmúrírun ni à ń pè ní 'Wọ́nwọ́n, wọ́nwọ́n, ọ̀wọ́n-rúnwọ̀nrán.' Orúkọ yìí ń fi hàn wá bí ara ẹni tí imú ń run kì í ṣe bọ̀ tí ó máa jòwèrè lọ síhìn sọ́hùn. Ifá wá sọ pé irú ìmúrírun báyìí kò gbọdọ̀ mú ọmọ Ifá tàbí ọmọ Odù. Ó tún wá ń sọ wí pé nígbà tí onìbéèrè yí ti rúbọ, ó ti di ọmọ Ifá, nítorí náà kí ìmúrírun ó tú u sílẹ̀:

> Ọmọ Ifá níyì o,
> Ọmọ Ifá níyì o,
> Ọmọ Odù ni é.
> Ẹ tú u sílẹ̀,
> Ẹ jẹ́ kí ó lọ . . .

Àwọn Yorùbá gbà gbọ́ púpọ̀ nínú ọfọ̀ pẹ̀lú júlọ ọfọ̀ Ifá tàbí àyájọ́. Wọ́n gbà pé Ifá mọ orúkọ àṣírí tí gbogbo àìsàn ń jẹ́. Bẹ́ẹ̀ náà ni Ifá ṣe mọ orúkọ ewé àti egbò kọ̀ọ̀kan, ó sì tún mọ orúkọ àṣírí àwọn ẹbọra àti irúnmọlẹ̀ tí ń gbé ilé ayé. Èyí nìkan kọ́. Ifá mọ gbogbo mọ́jẹ̀mu tí àwọn ẹbọra, àjẹ́ àti àìsàn oríṣìíríṣìí bá gbogbo àwọn òòṣà dá. Lẹ́yìn ìgbà tí Ifá bá pe ewé àti egbò ní orúkọ tí



wọ́n jẹ́, yóò pe ẹbọra, ajogun tàbí àjẹ́ tí ó fi àìsàn náà ṣe ẹ̀ẹ̀yàn ní orúkọ tí òun náà ń jẹ́, yóò pe àìsàn náà pàápàá ní orúkọ tirẹ̀, yóò náà lọ sí inú Odù tí ó sọ ìdí rẹ̀ tí àìsàn náà kò fi gbọdọ̀ ṣe ẹni náà bẹ́ẹ̀ nítorí àdéhùn ìgbàa ìbẹ̀rẹ̀ kan. Kíá ni àìsàn náà ó fi lọ.

Ìtumọ̀ èyí ni wí pé ojú ni Ifá máa ń bá àìsàn wí. Nínú ìtàn tàbí àdéhùn ayérayé ni Ifá ó sì tí má ṣẹ̀in ọ̀rọ̀ tí yóò fi ro ejọ́ náà jáde. Ìdí níyí tí ó fi yẹ kí ẹ̀ẹ̀yàn ó máa rúbọ, kí olúwarẹ̀ ó lè jẹ ọmọ àwọn òrìṣà, kí Ọ̀rúnmìlà ó sì fi lè ro ejọ́ nípa olúwarẹ̀ nígbà tí àìsàn bá dé.

## Ẹsẹ Ẹ̀karùn

Ohun tí Ifá ń wí nínú ẹsẹ yìí ni pe ikú yẹ̀ lóri ẹni tí ó dá Ọ̀wọ̀nrín Méjì. Àgbébọ̀ adìẹ ni ó rú ní ó gbé ikú olúwarẹ̀ lọ. Ẹni tí wọ́n kọ́ dá Ifá náà fún ní ayé àtijọ́ ni à ń pè ní Ọlọ́mọ̀bààkà ẹni tí í ṣe àkọ́bí Ọlọ́fin. Àwọn babaláwo t'ó dá Ifá náà jẹ́ mẹ́ta: àwọn kán kọ ilà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ kẹ̀kẹ̀, àwọn kán kọ ilà ìdúdà, àwọn kán sì kọ ilà tí à ń pè ní kolọ̀kolo. Wọ́n ní kí Ọlọ́mọ̀bààkà ó rúbọ nítorí ikú. Ó sì ṣe bẹ́ẹ̀. Ikú kò sì lè pa á mọ́, bẹ́ẹ̀ ni àrùn kò sì lè gbé e dè. Ó wáá ń jó, ó ń yọ̀. Ó ní:

> Àwòdì gbé ikún mi rá lọ tàn tàn,
> Àwòdì gbé ikún mi rá lọ tàn rèrè.

Ìtumọ̀ ẹsẹ Ifá yìí ni pé gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́mọ̀bààkà ti ṣe bọ́ lọ́wọ́ ikú àti àrùn lẹ́hìn tí ó rúbọ tán, bẹ́ẹ̀ gan-an náà ni ikú ó ṣe yẹ̀ lórí ẹni tí a dá Ifá yìí fún bí ó bá lè rúbọ. Ifá sọ wí pé àìsàn ń ṣe ẹni tí a dá ẹsẹ Ifá yìí fún. Àìsàn náà sì le jù ṣùgbọ́n bí kò bá rúbọ, ṣùgbọ́n bí ó bá le rúbọ, ẹbọ t'ó rú náà ni ó gbé ikú rẹ̀ lọ pàápàá t'ó fi jẹ́ wí pé ayọ̀ ni ọ̀rọ̀ rẹ̀ ó jẹ́ ní ìkẹhìn.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí tí wọ́n ki ní ọ̀nà ìbéèrè àti ìdáhùn ń fi àwítúnwí rẹ̀pẹ̀tẹ̀ ṣe ìdánilójú fún ẹni tí a dá Ifá yìí fún wí pé òun ó ṣẹ́gun ìre gbogbo fún onìbéèrè yí, òun ó sì tẹ̀lé mọ gbogbo ajogun. Àpèta ìgbàràńsaala tí wọ́n dárúkọ yìí jẹ́ ìbikan tí a máa ń máa ń mẹ́nubà nígbà gbogbo nínú ẹsẹ Ifá pẹ̀lú júlọ nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn àjẹ́ àti àwọn ajogun. Ọ̀pọ̀ ni àdéhùn tí a gbà wí pé Ifá bá àwọn ẹlẹ́yẹ tàbí àwọn ajogun ṣe lórí àpèta yìí. Nítorí náà, orúkọ àpèta yìí a máa hàn nígbà gbogbo nínú ọfọ̀ Ifá tàbí àyájọ́.

Ọ̀fọ̀ Ifá kan ni ẹsẹ yìí jásí. A ó ṣe àkíyèsí pé kò sí gbólóhùn 'A dìá fún' nínú ẹsẹ yìí nítorí pé ọ̀fọ̀ láśán ni, kì í sì í ṣe dandan kí gbólóhùn yí wà nínú ọ̀fọ̀ Ifá.

Dìlón yumuyumu àti kìkùn yumuyumu tí a ń sọ nígbà gbogbo nínú ẹsẹ Ifá yìí ń fi hàn wá pé gbogbo awọn ìre àti ajogun tí a dárúkọ náà kò jìnà sí onibéèrè yí. Ṣùgbọ́n bí onibéèrè náà bá rúbọ, àwọn ìre ni ó wọlé tọ̀ ọ́, Ifá ó ní í jẹ́ kí àwọn ajogun ó wá sí ọ̀dọ̀ rẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹkẹje

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa ìpò tí ọ̀gbọ́n kó nínú ìgbésí ayé ènìà ọ̀dá. Ó fi ọ̀gbọ́n wé owó, ó sì sọ wí pé ọ̀gbọ́n wúlò fún ẹni tí a fẹ́ẹ́ fi sí ipò olóri ju owó lọ. Wọ́n fi Ọ̀wọ́nrín j'oyè ilé baba rẹ̀ nítorí pé ọlọ́gbọ́n ni bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé kò ní owó lọ́wọ́.

Ẹsẹ Ifá náà sọ wí pé lárìn ọ̀pọ̀ ènìyàn, ó yẹ kí ọlọ́gbọ́n ó máa wà níbẹ̀. Bí kò bá sí ọlọ́gbọ́n láàrín ọ̀pọ̀ ènìyàn, wọ́n dà bí yúùnyun láśán tí a máa ń pa nínú oko fun ẹran jẹ:

> Ẹní pọ̀ tí ò gbọ́n,
> Ẹ jẹ́ á fi wọ́n wé yúùnyun nínú oko . . .

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa orígìí nókan tí ọ̀wọ́n á dá sílẹ̀. Ó fi orúkọ odò yí ṣeré nibi púpọ̀, ó sì fi ọ̀gbọ́n orígìírìgìí yọ nípa ọ̀wọ́n tí ó ń sọ̀rọ̀ bá. Kò sí nókan tí ọ̀wọ́n kò le fà. Kódà bí ọmọ bá wọ́n ọ̀ọ̀yàn tán, bí ọmọ bá jálẹ̀, wọn ó tìtìn máa wá ọ̀nà àti dá a láre tàbí kí wọn ó wá ìtumọ̀ tí ó mú un jálẹ̀ dìpò kí wọn ó bá ọmọ náà wí gìdìgbà wí pé ohun tí ó ṣe kò dára.

## Ẹsẹ Ẹkẹjọ

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí gìdìgìdì nípa ohun-ọ̀gbìn tí wọn ń pè ní kókò. Ifá ṣe àkíyèsí pé ìrírí ni kókò máa ń rúwé nígbà òjò; ṣùgbọ́n b'ó bá di ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn gbígbẹ ni ewé kókò máa ń gbẹ. Ó wá fi ìrànlọ́wọ́ tí òjò ń ṣe fún kókò wé èyí tí ọkọ ń ṣe fún ìyàwó rẹ̀. Ó wá tún ṣe àkíyèsí wípé pé kíkọ̀ tí kókò kọ òjò sílẹ̀ l'ó fà á tí ewé rẹ̀ fi ń gbẹ nígbà ẹ̀ẹ̀rùn tí kò sí òjò mọ́ láti ṣe ìtọ́jú rẹ̀.

Ohun t'ó fa ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀kà bá kókò ni wí pé ó ṣe àìgbọràn sí àwọn babaláwo. Wọ́n ní kí ó mú ko òjò sílẹ̀, kò gbọ́. Ó sì tún kọ̀ láti rúbọ:

> Ìgbà àgọ̀bọ,
> Ìgbà ààrin;
> Òjò ò rọ̀ mọ́,
> Ewé kókò ń gbẹ . . .

Nítorí náà pàtàkì nínú ohun tí Ifá ń sọ ní ìparí ẹsẹ náà jẹ́ ọ̀rọ̀ nípa ìyànu tí àìgbọràn àti àìrúbọ máa ń kó bá ènìyàn.



# 7 ÒBÀRÀ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹkìnì

Lọ́nà kìnní, ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí pàtàkì nípa ohun-ọ̀gbìn tí a ń pè ní bàrà. Bàrà a máa ní ọ̀pọ̀ púpọ̀, ṣùgbọ́n ilẹ̀ ni àwọn ọmọ aráyé máa ń lo ọ̀pọ̀ bàrà láti le sì ẹ̀gúsí inú rẹ̀ mú. Ẹsẹ Ifá yìí wá ń sọ pé àìrúbọ ọ̀nà l'ó fà á tí wọn fi ń lu bàrà. Ẹbọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ nìkan ni bàrà rú, kò rúbọ kí ọmọ̀ àwọn ọ̀tá ó mọ́ le tẹ àwọn ọmọ rẹ̀. Ẹsẹ Ifá yìí wá ń sọ pé àìrúbọ kò dára.

Ẹsẹ Ifá yìí sọ fún wa pé bàrà yàgàn púpọ̀ kí ó tóó lọ dífá. Ó fi bí bàrà ṣe yàgàn t'ó wọ bí àpóta ṣe ṣàfilẹ̀ṣẹ̀ lójú rẹ̀. Ó ní:

> Ó yàgàn,
> Ó yàpóta.
> Ó r'ọ́mọ lẹ́yìn ndìẹ̀, ó bá pàní ṣékun.

Nítorí náà ohun kejì pàtàkì tí ẹsẹ Ifá yìí ń tọ́ka sí ni ọ̀rọ̀ ọmọ-bíbí. Ifá sọ pé ọ̀pọ̀ ọmọ ń yọ́n ẹni tí a dá Ifá yìí fún. Ifá ní yóò bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ t'ó bá le rúbọ, ṣùgbọ́n k'ó rúbọ ọ̀tá kí àwọn ọmọ aráyé ó mọ́ pa àwọn ọmọ náà.

## Ẹsẹ Ẹkeji

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn kan nípa Ìkúnà-ọlá, ọmọ Olódùmarè, ẹni tí ó ṣìṣe lọ s'ílé Onikumogbóbì. Wọ́n kan ẹsẹ méjì fún un. Wọ́n ní k'ó mú àkùkọ gìrìpà l'Ọ́rún, k'ó sì mú òpókìpìkọ ẹyẹlé l'Ọ́dọ̀, ọ̀tẹ̀yìnjú ẹyẹ. Nígbà tí ó rúbọ tán, ó sì ní ìṣẹ́gun.

Odù tí a dárúkọ nínú ẹsẹ Ifá yìí ni à ń pè ní Ọ̀bàrà ìkọ̀kọ̀ nítorí pé àwọn babaláwo okàdà nìkan l'o lè fojúkàn án. Ẹyẹlé t'ó rúbọ

ìbádàá ni wọn fi máa ń bọ ọ́. Ìtàn sọ fún wa pé obìnrin Ọ̀rúnmìlà ni Odù. Nítorí pé ó jẹ́ ẹnìkan tí ó dára púpọ̀ ni wọ́n ṣe ń pé é ní 'Odù, ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́'. Ọ̀sun náà jẹ́ òòṣà kan tí àwọn babaláwo máa ń bọ. Orúkọ òòṣà yí ni àwọn babaláwo fi máa ń sọ ọmọ wọn ní Àmọ̀sún, Àmọ̀rẹ̀ àti Dàsúnmú. Orúkọ mìíràn tí à ń pe Òòṣà yí ni Ọ̀rẹ̀rẹ̀. Ọ̀pá kan báyìí tí a ṣe ọnà sí lára tí à ń pé ní ọ̀pá Ọ̀sún tàbí ọ̀pá Ọ̀rẹ̀rẹ̀ ni àmì òòṣà yí. Ọ̀pá náà kò gbọdọ̀ fi ẹ̀gbẹ́ kanlẹ̀. Ni wọ́n fi wí pé 'òòró gangangan l'a á b'Ọ́sùn'. Àkúkọ ìtùbí ni a fi ń bọ òòṣà yí.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Nínú ẹsẹ Ifá yìí a rí orísìírísìí ọ̀rọ̀ tí ọ̀pẹ̀ fi wúlò fún ènìyàn. Ẹsẹ Ifá náà dárúkọ ìgbàgo àti imọ̀ ọ̀pẹ. Ẹéyàn lè fi wọ́n dáná tàbí kí ó fi wọ́n bun agbọn. L'ára imọ̀ ọ̀pẹ kan náà l'a ti ń rí ọ̀ṣọ̀ tí a fi ń gbálẹ̀. L'ára ọ̀pẹ l'a ti ń rí epo tí a fi ń sebẹ̀, tí a sì fi ń jẹṣu. Ọ̀pẹ̀ náà l'ó ń so ẹ̀kùrọ́ tí a fi ń ṣe àdí tí a fi ń pa ojú, pa ara. Ẹsẹ yìí wá ń sọ pé ó yẹ kí ènìyàn ó máa fi iyì fún Ifá nítorí ìwúlò ọ̀pẹ̀ tí ó pọ̀ lọ rẹpẹtẹ yìí nítorí pé ọ̀pẹ̀ l'ó dúró fún àmì pàtàkì Ifá ní ayé yìí.

Ẹsẹ Ifá náà wá fi ìwúre parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ nígbà tí ó wí pé:

> Ẹ̀rìgì Àlọ̀, wá kí o wáá ṣọlà
> S'ílé èmi awo.
> Babaà mi, Ẹ̀rìgì Àlọ̀,
> Wá dandan, kí o wáá ṣọlà
> S'ílé èmi awo.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí sọ̀rọ̀ nípa àwọn ẹranko orísìírísìí. Ó júwe àwọ̀ ara àwọn ẹranko t'ó sọ̀rọ̀ bá nìà. Ó pe ekùn ní 'aláwọ̀ mọ̀dàrù mọ̀-dàrù'; ó pe ẹfọ̀n ní 'aláwọ̀ pòsòpòsò'; ìgbọ̀nrín ní 'aláwọ̀ mèlúmèlú'; ẹtà ní 'aláwọ̀ kínikíni'. Gbogbo àwọn àpèjúwe wọ̀nyí l'ó bá àwọn ẹranko náà mu régírégí.

Ẹsẹ Ifá náà wá sọ ìtàn kan nípa àwọn ọdẹ àti ẹranko agbègbè ìlú Ìkàrẹ́. Wọ́n kìlọ̀ fún àwọn ẹranko ìlú Ìkàrẹ́ pé kí wọn ó ṣebọ ẹbọ-ìyè, ṣùgbọ́n wọn ò rúbọ. Àwọn ọdẹ Ìkàrẹ́ nìkan l'ó rúbọ. Nígbà tí àwọn ọdẹ Ìkàrẹ́ dé'nú igbó, àrúbọ bẹ̀rẹ̀ sí í jẹ́ fún wọn; wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í pa àwọn ẹranko tí kò rúbọ náà. Ẹsẹ Ifá náà wá parí pẹ̀lú ìkìlọ̀ fún àwọn tí kì í fẹ́ rúbọ. Ó ní:



> Kírà ẹbọ ni i gbè ni,
> Àìrú kì í gbèèyàn.
> Ẹ tètè wáá bá ni ní àrùṣẹ̀gun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kàrún

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa ọba ìlú Ọwọ̀ tí à ń pè ní Olówo, agbọ́nrin, ọmọ olóṣo agogo. Ẹsẹ Ifá náà sọ wí pé ní ìgbà kan ọba náà ń bẹ láàrin òṣìṣẹ́ ọ̀tá ayé. Lẹ́yìn ìgbà tí Olówó rúbọ tán, ó sì ní ìṣẹ́gun. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í yin Ifá. Ó ní:

> Ifá dé, aláṣẹ,
> Ọ̀bara aláṣẹ,
> Kò mọ̀ mọ̀ sí ìrànmọ̀ bí Ifá.

Ohun tí Ifá ń wí nínú ẹsẹ yìí ni pé ẹni tí a dá Ifá yìí fún ń bẹ láàrin òṣìṣẹ́ ọ̀tá. Bí ó bá lè rúbọ, yóò ní ìṣẹ́gun.

Ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí, a rí orísìírísìí ìwà tí Ọ̀rúnmìlà ń hù nípa kí í máa ta nǹkan kan ní ìmìràn. Ẹsẹ Ifá náà ràn ni létí àlọkò ìwà ẹ̀rù nítorí pé ó ní:

> Baba l'ó ta Fúlàní ẹ̀ràdà,
> Baba l'ó taṣàṣà l'ó ra Làròkùlánì,
> Baba l'ó ta ẹrú n lọ fi rọmọ,

A lè fojú-inú ìwòrìnwà orísìírísìí tàbí ti agbára Ọ̀rúnmìlà láti nípa nǹkan títà. Bí Ọ̀rúnmìlà bá ta nǹkan kékeré bí aṣọ, ó lè ti ta ìdìdì èèyàn.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí ń fi agbára tí Ọ̀rúnmìlà ń fi í tún ayé ọmọ ẹ̀dá ṣe wé agbára tí a fi ń sọ ìgbà tí ó bá fọ́. Ó sọ ìtàn kan nípa bí Ọ̀rúnmìlà ṣe tún ayé ọba Ifẹ̀ kan ṣe bí ìgbà. Ó wá parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú ìdánilójú pé Ọ̀rúnmìlà ó lèèé ara tún Ifẹ̀ wa ṣe:

> Ifá ni yóò tún Ifẹ̀ẹ̀ wa ṣe
> Ẹ̀là Ìsòdè.

Ìfọ̀rọ̀wérọ̀ orísìírísìí pa ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí jẹ. Bí ó bá lọ àwọn alálòó ohun òkè ọ̀dẹ̀, yóò fi àwọn alálòó ohun ìsàlẹ̀ gbá a lẹ́sẹ̀:

> Baba Abíríyómú,
> L'ó bí Abíríyómú.

Baba Abiriyàmù
L'ó bí Abiriyàmù.

Ẹsẹ Ifá náà wáá ti ibi ìtọ̀rọ̀gìnì yìí sọ̀rọ̀ dé ibi ìtàn ẹnìkan tí wọ́n ń pè ní 'baba Abiriyàmù' tí ó bí sí ibi kan tí ẹnikẹ́ni ò mọ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Olúm tí Ifá ó wí nínú ẹsẹ yìí ni pé ọ̀kan gọngọ pínú lókànrin dún mọ lọwọ̀ olọ. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe àlàyé ewu orìṣìríṣìí tí ó lè n'llé ẹni tí ó ní obìnrin kan tabi jù bẹ́ẹ̀ lọ. Díẹ̀ nínú àwọn ewu wọ̀nyí ni ìfólà, pamúkà, àjàgbilà àti mùtùtú. Ewu mìíràn ni kí á máa purọ́ mọ Ifá ọlọ ẹni. Ẹsẹ Ifá yìí kò sọ pé kí ọ̀kọ́yàn ó mọ́ níí obìnrin púpọ̀, nínú t'ó ń sọ ni pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewu l'ó wà nibi kí á ní obìnrin púpọ̀.

Ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí, ní ibi ọ̀rọ̀kọ àwọn babaláwo, Ifá ń sọ ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa odò yìyí àti ìkòkò yìyí. Ó ní bí a ṣe yí odò, ẹnìkan kì í yí ìkòkò bẹ́ẹ̀. Ó ní:

Ìyí a yiri,
Kì á mọ̀ mọ̀ yí ìkòkò.
Bí a yí ìkòkò inú alámọ̀ a bàjẹ́.
Odò ni ìgì,
Ìkòkò lamọ̀ . . . .

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ìtàn ní ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa Ọba ilú Ìbíní tí a ń pè ní ọba Adó. Àrọ̀jà omlọ ilú yìí ni Adó Ìbíní. Ọba yìí kówó, ó lọ́rọ̀ papàá jùlọ, ó ní ìlẹ̀kẹ̀ orìṣìríṣìí. Ṣùgbọ́n kò ní bàbá. Ìsọmọ̀ òyì ni pé kò ní àtàn tí ó yọ ìpò rẹ̀ ayọ̀ bí ọba ilú. Nígbà tí ọba Adó rúbọ tán, ó di mọ́lẹ̀, ó sì di ọ̀pẹ̀tàn ilẹ̀. Ilẹ̀ rẹ̀ pọ̀ to bẹ́ẹ̀ t'ó fi jẹ́ pé a máa ń wí nípa ọba tí ó bá ní ilẹ̀ púpọ̀ pé ó nílẹ̀ bí Adó. Ifá wá fi ìgbàlàa ọba Adó wé ìgbàlàa ìgbá òkè tí ó dúró tagbàra tagbàra. Ó ní:

Àwà dunlẹ̀,
A ò kò mọ́.
Àwà d'ìpẹ̀tàn ilẹ̀.
Àwà dunlẹ̀ bí Adó.
A d'ìgbó òkè,
A lè gbọ̀ngbọ̀n.



# 8 ỌKÀNRÀN MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kìní

Ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ yìí, Ifá ń sọ pé ìwà dé bí a bá ti dá Ọ̀kànràn Méjì. Ó wá dárúkọ orìṣìríṣìí ewé tí ó wà ibi dánù fún onibeere náà.

Ewé àjẹ̀fọ̀ló ni yóò fa ibi rẹ̀ l'ẹ́sẹ̀ wa,
Ewé ẹ̀jìnrín wẹ̀rẹ̀ ni yóò wẹ̀ ẹ̀ dànù.
Ewé atapàrá l'ó ní kí ibi ó ta mọ́ l'ẹ́sẹ̀ mi.

Gbogbo ewé mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a dárúkọ yìí ni àwọn babaláwo ó ti ṣe Ifá fún onibeere náà kí ori rẹ̀ ó lè bàà sọ̀rọ̀.

Ẹsẹ Ifá yìí tún wáá sọ ìtàn kan nípa Ọ̀rúnmìlà. Ó ní Ọ̀rúnmìlà mú eku, ẹja, ẹyẹ àti ẹran ní mẹ́jìmẹ́jì, ó fi bọ orí rẹ̀, orí náà sì mọ́ kedere. Orí onibeere yí kò mọ́ rárá. Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rúnmìlà ṣe bọ orí rẹ̀ t'ó mọ́ kedere àwọn babaláwo ó fi àmìbọ àti ewé Ifá bọ orí onibeere náà mọ́.

Ní ìparí ẹsẹ náà ni a ti rí ìtàn kan nípa Ọlọ́fin. Ẹsẹ Ifá yìí sọ pé ní ìgbà kan ìlàn burúkú kan kọlu Ọlọ́fin tí ó fi dà bí ẹni pé 'Ọlọ́fin á ranrẹ̀'. Àwọn, ayọ Ọlọ́fin, náà sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe àìsàn ìgbóolú kan bàyìí; bẹ́ẹ̀ sì ni Ọ̀kàndè, ọmọ Ọlọ́fin, ń ṣe òyungede. Ṣùgbọ́n nígbà tí Ọlọ́fin rúbọ tán, gbogbo wọn l'ó gbádùn.

Ombolú gba dùdú;
Oràfunfun gba funfun;
Aláyàwin gbàyìnrìn;
Bàràpetù wáá kórìn gbogbo lọ.

Èyí ni wí pé bí onibeere yí bá le rúbọ tí àwọn babaláwo kà fún un, gbogbo àìsàn tí ń ṣe é àti àwọn ará ilé rẹ̀ yóò tó ó san pátápátá.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ẹranko ilẹ̀ méjì àti ẹyẹ oko kan. Àwọn ẹranko náà ni erin àti ẹfọ̀n, ẹyẹ náà sì ni ìrìngùn mọ̀nà. Wọ́n ní kí gbogbo wọn ó rúbọ. Wọ́n ní kí erin ó rúbọ nítorí kí ó le bàà kọ̀. Wọ́n ní kí ẹfọ̀n ó rúbọ nítorí kí ó le bàà mọ̀. Wọ́n ní kí ìrìngùn mọ̀nà ó rúbọ nítorí kí ó lè ní ọ̀nà tí yóò jù gbogbo ẹyẹ oko lọ. Gbogbo wọn l'ó

rùbọ, wọ́n sì ní ohun tí wọ́n ó ṣe. Ṣùgbọ́n ohun t'ó fà á tí ìràngan mọ̀ọ̀ lò fi nlẹ̀ t'ó jẹ́ wí pé ẹ̀rù kàn Fà ní ni wí pé ẹbọ rẹ̀ kò tó ìhan. Ìràngan mọ̀ọ̀ ní ẹ̀rù Ìten, ṣùgbọ́n kò níyì rárá. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í wá iyì kààkiri. Ó ní:

Ẹ sùnú wá,
Ẹ wáà gbé'yì fún mi.
Èmi ni ìràngan mọ̀ọ̀.
Ẹ sùnú wá,
Ẹ wáà gbé'yì fún mi.

Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Púpọ̀ nínú àwọn ìlò ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ orìkì Ọ̀rúnmìlà. Ẹsẹ Ifá yìí ki Ọ̀rúnmìlà ní: 'Ọmọ elépo lọ́pọ̀, Ẹ ò jàlì . . .' Ọ̀pẹ́ jẹ́ àmì yẹ̀tàkì fún Ọ̀rúnmìlà. Nítorí náà, a lè ki Ọ̀rúnmìlà ní ọmọ elépo. Ohun tí ó fà á tí Ọ̀rúnmìlà kì í fi í jẹ àdí ni pé ó ti ní epo tí ó tó o ó jẹ. Ṣé bí ẹ̀yìn ò bá rọ̀po aṣẹ lò lò lo àdí.

Ẹsẹ Ifá yìí tún ki Ọ̀rúnmìlà ní 'ẹkún ìgran sún'. Kò sí ọjọ́ kan tí wọ́n kì í fi ẹran, ẹja tàbí ẹyẹ bọ Ọ̀rúnmìlà. Èyí ni ìdí rẹ̀ tí wọ́n fi pè é ní 'ẹkún ìgran sún'.

Wọ́n tún ki Ọ̀rúnmìlà kan ìlẹ̀kẹ̀ sọ̀gì nínú ẹsẹ Ifá yìí. Nínú orìkì yì, wọ́n tún dárúkọ àwọn ìlẹ̀kẹ̀ oníyebíye mẹ́jì mìràn: àkún àti okùn. Àwọn ìlẹ̀kẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí jẹ́ ìlẹ̀kẹ̀ tí àwọn olórí àti ọlọ́rọ̀ ilẹ̀ Yorùbá máa ń fi í ṣe ọ̀ṣọ́. Wọ́n kì í ṣe ìlẹ̀kẹ̀ tííkàà rírí. Nítorí náà, ohun tí a ń wí nínú orìkì yí ni pé ọmọ ọlọ́rọ̀ ni Ọ̀rúnmìlà.

Ẹsẹ Ifá náà wá ṣàwí pẹ̀lú ìdánilójú pé gẹ́gẹ́ bí adìẹ funfun ṣe jẹ́ 'àgbà ààyò àkùkọ', bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà ni ẹni tí ó gbékẹ̀lé Ifá ṣe jẹ́ ààyò Olódùmarè. Olódùmarè kì í gba ẹbọ lọ́wọ́ ẹnikan kan. Ẹbọ àti ìrúbọ fún Olódùmarè. Ṣùgbọ́n bí a bá ti rúbọ fún àwọn òòṣà tí a ti sin, Olódùmarè nìkan yóò sì ní.

Adìẹ funfun, àgbà ààyò àkùkọ.
Ta ni le f'Olódùmarè lẹ́bọ?
Èmi nìí d'adìẹ funfun,
Àgbà ààyò Olódùmarè.

Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá kẹ́rin yìí sọ ọ̀rọ̀ púpọ̀ nípa ìkọ̀kọ̀. Ó kọ́kọ́ sọ pé ìrẹ̀kànná ọwọ́ kò ṣé lọ́wọ́ tagatago. Bí ewé bá ti wà l'ára igi, bí a bá



á fi ìrẹ̀kànná bọ̀ ọ́, kò ní í kan ní lára dáadáa nígbà tí a bá kà ọ̀pẹ̀ rẹ̀. Ẹsẹ Ifá yìí wá pa òwe kan. Ó ní: 'Ohun rere ní í yọ ilẹ̀ lọ́pọ̀, Ohun búburú ní í yọ ilẹ̀ nínú apẹ̀'. Ìtumọ̀ èyí ni pé bí ẹnikan bá ṣe ohun tí ó dùn mọ́ ni, a lè tọ́ọ̀ ìtọ́wò, k'á fún un ní ohun láti fi hàn wí pé ó ṣe nǹkan t'ó wù ni lóòótọ́. Ṣùgbọ́n bí ẹlòmíràn bá ṣe nǹkan t'ó bí ni nínú, a lè fi ìbínú yọ ohun-ìjà jáde, kí á sì bẹ̀rẹ̀ sí í bá a jà.

Ẹsẹ Ifá yìí wá sọ̀rọ̀ nípa oko àgbẹ̀ àti ìjìmèrè. Àwọn ẹranko mẹ́jèèjì tí a dárúkọ yìí a máa jí nǹkan mú nínú oko olóko. Bí olóko ò bá kú, tí ìjì ògìnìnbẹ̀rẹ̀ tí wọ́n ó máa fà l'órí rẹ̀ ó sì ya, kò ní í sí ìgbà t'ón àwọn ẹranko mẹ́jèèjì yí lè i rí nǹkan jẹ nínú oko olóko. Bí àwọn àgbẹ̀ bá sì jẹ́ ti wọ́n yó tán, wọ́n a máa sáré l'órí igi. Ní Ifá fi wí pé:

Kòlòkò mọ́ mọ́ lọ o,
Kí ògìnìnbẹ̀rẹ̀ mọ́ mọ́ ya.
Ní ìwọ̀yí àmọ́dún
K'á rìbì jọ gbàáńgbá.

Ẹsẹ Ẹ̀karùn-ún

Nínú orúkọ àwọn babaláwo t'ó wà ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí, a rí àìkan nípa babaláwo kan t'ó gbọ́n tí t'ó fi dá ìlú tí wọ́n ń pè ní Mọ̀jàlawa. Babaláwo tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí náà t'ó tún pàjùbà tíì t'ó fi ìyà kan oko ìlú tí a ń pè ní Mọ̀jàlawa yìí náà. Nígbà tí wọ́n kọ́ṣẹ́ babaláwo yìí ní ìlú Mọ̀jàlawa, wọ́n wá sọ pé kí olóko ó máa mú mọ́, kí olódo ó mọ́ odò mọ́. Nígbà tí wọ́n gbé a oko ní ìlú yìí, wọ́n bá ẹ̀yin ọlọ́gẹ̀ẹ̀dẹ̀ nínú oko, wọ́n sì bẹ̀ orí ohun kálá. Wọ́n rò pé ìdí ìbínú, wọ́n bá abuké kan l'ábà Ọ̀ṣà, ẹni tí orìkì rẹ̀ ń jẹ́ 'ẹ̀rù, ọmọ ọ̀jìjì'. Nígbà tí wọ́n wá ṣẹ́ṣẹ̀ fà ìlàlàlà bọ̀ọ́ tán ni wọ́n wá rí i pé ará tí bẹ̀rẹ̀ sí kan àwọn.

Àwọn babaláwo tí a dárúkọ orúkọ wọn sókè yìí t'ó wá dá Ifá fún àwọn ìlú Ọmọ tí a ń kì ní 'Lámú, apẹ̀rùn, ọmọ oba sí í pa wọ́n lẹ́sìn jẹ'. Ẹsẹ Ifá yìí wá sọ pé ẹ̀rù ò ba àwọn ẹ̀yin ìdíìyàn ìlú. Àṣẹ babaláwo t'ó ń bá wọ́n kẹ́rù.

Ẹsẹ Ifá yìí wá ṣàwí pẹ̀lú ìtàn mìràn nípa Ọlánrán Mẹ́jì ẹni tí ó ṣe ohun ẹ̀rù, ṣùgbọ́n tí wọ́n ò bá a wí rárá. Ìpari ẹsẹ Ifá náà jẹ́ ìròyìn pé bí Ọlánrán Mẹ́jì ó bá babaláwo ṣe ọ̀tà rẹ̀.

Ọ̀tá awo, odì awo,
Ẹ ò ònìlà kùngbùlì lè wọ́n pa mọ́lẹ̀.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa ire ọmọ. Ẹsẹ yìí ni a dá fún ọníkan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Olúnlóyè nígbà tí ọkàn rẹ̀ fi bàjẹ́ nítorí àìrọ́mọbí. Àwọn babaláwo t'ó dá Ifá fún Olúnlóyè ní ọjọ́ náà jẹ́ bọ̀rí mẹ́ta: àwọn kìnì ní kọ̀kọ́, àwọn kìnìbu àbàjà, àwọn kàn sí kọ ilà tí a ń pè ní ture. Wọ́n wá sọ fún Olúnlóyè pé k'ó má ṣe bínú rárá nítorí àìrọ́mọbí nítorí pé láìpẹ́ yóò bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ. Wọ́n ní:

Olúnlóyè, mọ̀ mọ̀ bínú o.
Olúnlóyè, mọ̀ mọ̀ ṣe rẹ̀dìm ọ̀ràn.
Àgbà tí kò bínú kọmọọ rẹ̀ẹ̀ pọ̀ . . . .

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹje

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn kan nípa Ṣàngó. Ó sọ pé ní ìgbà kan tí Ṣàngó fi wà láàrin ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọtá, ó lọ sọ́dọ̀ àwọn babaláwo tí à ń pè ní 'Jìnìjìpe, Jìnìjìpe'. Àwọn l'ó dá Ifá fún Ṣàngó ní ọjọ́ náà. Wọ́n ka ẹbọ fún Ṣàngó; ó sì rú u. Nígbà t'ó rúbọ tán, ó ṣẹ́ ní ìṣẹ́gun. Ṣùgbọ́n Ọ̀rúnmìlà kìlọ̀ fún un pé kò gbọdọ̀ bá àwọn ọmọ òun jà. Ìdí nìyí tí Ṣàngó kò fi gbọdọ̀ bá babaláwo jà. Ó ní:

Àfi ìkẹ́ o,
Àfi ọ̀ṣẹ̀ẹ̀.
Bí Ṣàngó bá pawo,
Ifá l'ó dá.
Àkẹ́ o,
Àfọ̀dàlẹ̀.

Ìtumọ̀ èyí ni pé Ṣàngó ó gbọdọ̀ pa babaláwo àfi babaláwo t'ó bá gbékè tàbí tí ó bá dalẹ̀.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Ohun tí Ifá ti wí níhìn ni pé ọ̀ràn ọmọ tí a dá Ọ̀kànràn Méjì fún ti di gígùn ná. Kí ó rúbọ fún Ògún. Ọ̀ràn ẹlẹ́yìí ó gùn gẹ́gẹ́ bí ìwájú àti ẹ̀yìn ọmọ. Ifá sì tún sọ pé òun ó bá ẹlẹ́yìí ṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀ bí ó bá lè rúbọ.



# 9 ÒGÚNDÁ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹ̀kínní

Ọ̀rúnmìlà ni Ìrìgbì Àlọ̀ tí a sọ pé yóò jagbọ́n obì nínú ẹsẹ Ifá yìí. Ohun tí wọ́n ń sọ níhìn ni pé kí ẹni tí a dá Ifá yìí fún ó fi agbọ̀n obì kan rúbọ fún Ọ̀rúnmìlà, kí ó ba náà ni ire ọmọbìnrin náà ó tóó wá wọlé tọ̀ ọ́.

Nínú orúkọ àwọn babaláwo t'ó dá Ifá yìí wọ́n dárúkọ kanranjangbọ̀n tí í ṣe ìtàkùn kan báyìí tí ń hù nínú igbó. Ìtàkùn náà jẹ́ ìtàkùn kan tí ó ń gbé inú igbó tàbí ní inú odò ọ̀dàn tí ó dàbí igbó. Ọ̀jàlà ni a tún ń pè ní erè. Ohun ni ẹjọ t'ó tóbi jù lọ.

### Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Pàtàkì nǹkan tí ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ lé ni òkò. Ẹsẹ Ifá náà sọ pé pàtàkì ìdí tí ẹ̀yán fi ń rúbọ ni òkò.

Ǹjẹ́, ẹbọ kín l'akápò ń ṣe?
Ẹbọ òkò l'akápò ń ṣe.

Ẹsẹ Ifá náà wá kè pe Ifá pé kí ó má jẹ́ kí akápò 'ó rìn lọ'. Èyí ni pé kí Ifá ó má jẹ́ kí akápò ó sìn lọ tàbí kí ó jáde lọ́gé. Ó tún wúre pé kí Ifá ó má jẹ́ kí ilé akápò ó bàjẹ́.

Àwọn babaláwo t'ó dá Ifá yìí jẹ́ ará ìlú méjì: Òkò tàbí Òhkò. Òkò jẹ́ ìlú pàtàkì ní ayé àtijọ́ nítorí tí ó kọ́kọ́ dá lé ọ̀nà ìlú fún ilẹ̀ Ọ̀yọ́ nígbà kan rí. Ìlú kan sì tún wà ní ẹ̀bá Ògbómọ̀ṣọ́ ní lọ́wọ́lọ́wọ́ tí a ń pè ní Òkò. Òhkò ni orúkọ tí à ń pe odò àwọn ará òkè Ògùn ní agbègbè Ọ̀yọ́.

### Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìbéjì méjì pàtàkì: Ọ̀rúnmìlà àti Ògún. Ó sọ pé ìgbà kan wà tí Ọ̀rúnmìlà wà nínú ìṣẹ́, tí ojú rẹ̀ pọ́n koko fún kàdàrà, tí ọrùn rẹ̀ sì wọ̀ pẹ́rẹ́pẹ̀rẹ̀ bíi wàhálà. Ó ní Ifá wá ń sunkún pé òun kò ní apá tí òun ó fi ṣe agbára. Ṣé ohun tí àwọn babaláwo gbà gbọ́ ni pé kò sí ìrugun l'ára Ọ̀rúnmìlà. Nítorí náà, ó ṣèrò fún un láti ṣe òkan agbára. Bí Ọ̀rúnmìlà bá fẹ́ ṣe nǹkan líle kan, ẹsẹ Ògún l'ó máa ó lò.

Ẹsẹ Ifá yìí tún sọ̀rọ̀ nípa Ògún. Ó kọ́kọ́ bí Ògún pé ológbon àti jagunjagun ni. Lẹ́hìn náà Ifá wá ṣe àlàyé pé bí Ògún kò bá dá èèyàn nìkan, ara kò le rọ̀ ọ́.

Ṣọ́ ìgbà tí Ògún dá ni nìkan
Lara tiwọn rọ ni.

Itumọ̀ èyí ni pé onibèèrè yìí nílò̀ ríbọ fún Ògún bí ó bá fẹ́ kí ara ó rọ̀ òun. Ohun ti pọ̀n ẹni ti a dá Ògúndá Méjì fún. Ṣùgbọ́n b'ó bá rúbọ fún Ògún, ara ó rọ̀ ọ́.

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Ọ̀rọ̀ Ifá ni ẹsẹ Ifá yìí. Olùwo tí Ifá ó wí nibẹ̀ ni pé bí ẹnìkan bá ní òrò bàbàrà sí onibèèrè yìí pé k'ó mọ̀ padà s'ílé rẹ̀ mọ́, dandan ni pé bí ẹni tí ó ní irú ọkàn bàbàrà bẹ̀ẹ̀ ó ti kú kí onibèèrè yìí ó tó padà dé'lé.

Ògún ni a kọ́kọ́ dá ẹsẹ Ifá yìí fún. Nítorí náà, onibèèrè yìí nílò̀ rúbọ fún Ògún fún ìṣẹ́gun. Ifá sọ wí pé onibèèrè yìí fẹ́ lọ sí ìrìn-àjò kan. Àwọn kan ń bẹ tí wọn ó fẹ́ kí ó padà tí ibẹ̀ bọ̀. Kí ó rúbọ kí ó lè borí ni ìṣẹ́gun. Bí ó bá le rúbọ dáadáa, àwọn tí wọn ń gbèrò bàbàrà sí onibèèrè yìí ni ìjàmbá ó padà wá ṣe kí onibèèrè náà ó tó padà délé.

## Ẹsẹ Ẹkarùn

Ifá ní ẹni tí a dá ẹsẹ yìí fún ń bẹ láàrin àwọn ọ̀tá. Kí ó fi àwọn wọ̀n kan kún ẹbọ rẹ̀. Bí ó bá le rúbọ dáadáa, Ọ̀rúnmìlà ó ba a ṣẹ́gun ọ̀tá rẹ̀. Àkókò kan wà tí Ọ̀rúnmìlà náà tí wà láàrin ọ̀tá ní ayé àtijọ́. Àwọn babaláwo ṣefá fún un, ó sì ní ìṣẹ́gun. Bí onibèèrè yìí náà bá le rúbọ, yóò ní ìṣẹ́gun.

Onírú, onírọ̀, olùlùbọ̀ọ̀ àti olóta tí a mẹ́nu bà nínú ẹsẹ Ifá yìí dúró fún orúkọ àwọn ọ̀tá tí ó ṣe elèyíì lẹ́nu. Kíkó ẹni ọ̀tá dá sínú àwọn wọ̀n tí a sọ nǹkan ni pé àwọn ọ̀tá náà kò ní í le ṣẹ́nu sọ̀rọ̀ lati ṣe ibajẹ́ elèyíì mọ́ nígbà tí ó bá rúbọ tán.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí àwọn ẹyẹ méjì pàtàkì: àkókò àti àrọ̀nì. Àkókò tí a tún ń kì ní 'mọ̀jàlawa' jẹ́ ẹyẹ oba ní ode Ọ̀yọ́. Àrọ̀nì ni ẹyẹ Oníkòyí tí ó máa ń so fún oba yìí àkókò tí ogun bá ń bọ̀. Àwọn



ẹyẹ méjèèjì yí fẹ́ràn olówó wọn dé ibi wí pé nígbà tí ìwà jà láàrin Ọ̀yọ́ àti tí Ìkòyí, àwọn ẹyẹ wọ̀nyí kọ̀ láti jade kúrò nínú ilé. Wọ́n sì fi bẹ́ẹ̀ jóná sínú láàrin ọ̀ba.

## Ẹsẹ Ẹkeje

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn ìjà kan tí ó ṣẹlẹ̀ láàrin Ìwàǹmìkàlẹ̀yìn, ọmọ Ẹni Adó, àti Ifá. Ẹni tí ó dá ìjà náà sílẹ̀ ni Molóógbéjà, ọmọ Ọ̀dọ̀fin, ẹni tí ó 'fòkòlò mẹ́ran l'ọ́bẹ̀ ilé'.

Olùwo tí Ifá ń wí nìhìn ni pé elèyíì ó ṣe ìkan kan t'ó lè fa ìjà. Kí ó rúbọ kí ìkà ó mọ̀ bàá pa á o.

Bí ìjà, bí ìjà ni ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí náà jẹ́. Ìgbàwìkì tí í ṣe awo ilé ìgbaràkì kò kí wọn mọ̀ nínú ilé náà, ó di ọ̀tá wọn nílẹ̀. Ìgbaràjà tí í ṣe awo wọn l'ódò Ìgbaràjà náà di ọ̀tá wọn ní òde Ìgbaràjà.

## Ẹsẹ Ẹkẹjọ

Ọ̀rọ̀ nípa ìre ọmọ ni ẹsẹ Ifá yìí dá lé lórí. Ó sọ ìtàn ẹnìkan tí ó ń pè ní Oyéùkókú tí ojú ọmọ pọ́n púpọ̀ nígbà ènìyàn tí ó bímọ ní ọjọ́ ogbó rẹ̀. Nígbà tí ó rúbọ tán, ó wá bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ. Nítorí pé ó fi arúgbó ara bímọ ni a fi ń pè é ní:

Ọ̀bọ̀ ìbùkú,
Agbàlagbà sẹ́ṣẹ̀,
Arúgbó ṣe lógo.

Olùwo tí Ifá ń wí nìhìn ni pé àgàn kan wà t'ó ti fi darúgbó. Bí ó bá le rúbọ, yóò bímọ púpọ̀ láyé.

# 10 Ọ̀SÁ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹkìní

Ifá ń ṣe ìkìlọ̀ nìhìn fún ẹni tí ó dá Ọ̀ṣọ̀rìn Méjì pé olówó ó níl ìre gbogbo bí ó bá le rúbọ. Ifá wá fi ìtàn Ọ̀rúnmìlà ṣe àpẹẹrẹ. Ó sọ pé nígbà kan, Ọ̀rúnmìlà, ẹni tí a tún ń pè ní Ọ̀ṣọ̀ yèkété, gbọ́ àwo lọ sí ìlú Ìwẹ̀ré. Wọ́n ní kí Ọ̀rúnmìlà ó rúbọ, ó sì rú u. Nígbà t'ó rúbọ tán, ó sì ní ìre gbogbo ní òde Ìwẹ̀ré. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í yìn

àwọn aara t'ó dá Ilá fún un, tí orúkọ wọn ń jẹ́ 'Kérèjè Ọwinrin, Ọwinrin kérèjè'. Ilá wá sọ pé àwọn ará ilú Ìwéré jẹ́ olówó pûpọ̀ ní ayé àtijọ́. Ó ní:

> Ṣé a o láájé bíjé
> Bí ará òde Ìwéré.
> Kérèjè Ọwinrin,
> Ọwinrin mú kérèjè . . .

## Ẹsẹ Èkejì

Ẹsẹ Ilá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa àbíkú. Àwọn Yorùbá gbà pé bí obìnrin bá ń bímọ, tí ọmọ náà sì ń kú ní tẹ̀lé-ntẹ̀lé, àbíkú ni ó ṣe ọmọ náà lọ́wọ́. A tún gbà gbọ́ pé àwọn àbíkú yìí wà nínú ẹgbẹ́ kan l'ọ́de-ọ̀run tí gbogbo àwọn àbíkú ọmọ wà. Láti inú ẹgbẹ́ yìí ni àwọn àbíkú ti máa ń yan àsà wọn wá sáyé láti wá yọ̀ iyá àti bàbá wọn lẹ́nu. Nítorí náà, bí ẹ̀yàn bá fẹ́ dá àbíkú, ó ńláti bẹ àwọn ẹgbẹ́ ọ̀run yìí kí wọn ó mú ráàn ọ̀kan nínú wọn sí ìdìrọ̀ ẹni tí àbíkú ń yọ lẹ́nu náà mọ́. Àwọn ẹgbẹ́ ọ̀run yìí ni wọ́n pè ní 'ẹ̀yin ajeni' nínú ẹsẹ Ilá yìí.

Àwọn Yorùbá gbà pé ẹ̀yàn lè de àbíkú ọmọ mọ́lẹ̀ sí ayé yìí lẹ́hin ìgbà tí olúwarẹ̀ bá ti rúbọ tí ó sì bẹ àwọn ẹgbẹ́rùn àbíkú náà tán. Ṣùgbọ́n ọ̀bẹ̀ l'ó ṣe nípa ọ̀rùn àwọn ẹgbẹ́rùn àbíkú yìí. Ìdí nìyí tí ẹsẹ Ilá yìí fi tẹnumọ́ ọ̀bẹ̀ ní kíkàn kíkan.

> Ẹyin ajeni,
> A bẹ yín o.
> Ẹ má ṣe l'ábíkú ṣẹ̀hìn wa mọ́ o.
> A bẹ̀ yín o.
> Ẹ gbọ́bẹ̀ . . .

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ẹsẹ Ilá yìí ń tọ́ka sí ìṣẹ̀ pàtàkì kan tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe. Ìṣẹ̀ yìí ni ìṣẹ̀ ìgbà-lákà àtí yeye-ẹlẹ. Àwọn Yorùbá tí ń gbe ìnú ọdún l'ó ní ìṣẹ̀ yìí. Ní ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn ni ìgì ìgbà máa ń rúwé, tí ó sì máa ń so. Ní àkókò àṣẹ̀lurẹ̀ òjò ni níkan bí oṣù kẹrin tàbí dé ìkẹ́fà ọdún ni ẹ̀yàn máa ń ká ìgbà. Ìgì àdàyébà ni ìgì ìgbà í ṣe. Nítorí náà ẹni tí ó ni ilẹ̀ tí ìgì ìgba bá l'órí rẹ̀ l'ó ní ìṣẹ̀ láti ká ìgbà náà. Àwọn mìíràn a máa ṣa ìgbà kíákíá ní àkókò tí òjò alátẹ̀gùn bá ń rọ̀ nítorí pé ìgbà a máa já lulẹ̀ ní àkókò yí. Ẹnikẹ́ni l'ó lè ṣa ìgbà t'ó bá já lulẹ̀.



Bí ẹ̀yàn bá ká ìgbà tán, olúwarẹ̀ a bàá bàá ara rẹ̀ kòró kí ẹ̀ṣọ papa ìnú ìgbà ó lè fara hàn. Ẹ̀ṣọ papa yìí ni a fi ń ṣe iyere. Lẹ́hin ìgbà tí a bá bó ìgbà tán, a ó lọ̀ ẹ̀ṣọ papa tí a rí nínú rẹ̀ kúnà. A ó lọ papa yìí dáradára, yóò sì ku kòró ìnú ìgbà nìkan. Kòró yìí ni à ń pè ní iyere.

Bí ẹ̀yàn bá lọ iyere tán, yóò sa a tí ó fi gbẹ. Bí ó bá gbẹ tán, olúwarẹ̀ lè tà á fún àwọn tí ń ṣe irú lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀. Ṣùgbọ́n bí ẹ̀yàn bá fẹ́ rí owó púpọ̀ nínú iyere náà, olúwarẹ̀ lè fi pamọ́ títí di ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn nígbà tí iyeré máa ń wọ́n. Ẹni tí ó bá lè ṣe eléyìí á rí owó rẹpẹtẹ nínú iyere títà.

Ohun tí ẹsẹ Ilá yìí ń sọ ni pé nígbà ẹ̀ẹ̀rùn ni iyeré máa ń tà. Bí ẹ̀yàn bá lè fi ìpọ́njú sẹ́gbẹ́ iyere nígbà òjò, tí olúwarẹ̀ sì fi pamọ́ títí di ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn kò ní ìpọ́njú mọ́ fún olúwarẹ̀. Ohun tí ó fà á nìyí tí Ilá fi wí pé:

> Nígbà òjò ni ìpọ́njú ìṣẹ́yeré mọ,
> Bí ó bá dìgbà ẹ̀ẹ̀rùn tán,
> A di onígba okùn,
> Wọn a di onígba ìdẹ . . .

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ọrọ̀ nípa orí ni Ilá ń sọ níhìn. Ọ̀rúnmìlà ni kì í ṣe gbogbo ẹ̀yàn l'ó yan orí ọmọ tàbí ọlà. Nítorí náà kì í ṣe gbogbo ẹ̀yàn ni a ó fi pọ́nl sin. Ẹlòmíràn ó kúú sìgbà, ẹlòmíràn ó kúú ogun lọ. Ẹlòmíràn ó tẹ̀ẹ̀ ká gẹ́gẹ́ bí akoṣẹ̀ tí yóò fi jẹ́ pé àwọn ẹ̀yàn rẹ̀ kò ní í lè fi pọ́nl sin in. Èyí ni ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tí Ilá sọ wí pé:

> Bí ó bá ṣe orí pé
> Gbogbo orí gbogbo ní í sun pọ́nl,
> Ìrókò gbogbo ìbá ti tán nígbó.

Ọ̀rúnmìlà tún wá ṣe àlàyé pé ìwa-ìjàlà kì í fẹ́ tètè gba ìpín tí a yàn n'Ílé Olódùmarè. Nítorí náà, a ó máa jówèrè lọ́yà a lè sí ìpín rere kò. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó ti jẹ́ wí pé àyànmọ́ kò ṣeé yẹ̀, yàn ní iyẹ́wù ìwéré ọ̀rọ̀ ẹ̀yàn kì í já sí rere nínú. Ilá sọ ọ̀rọ̀ kíkorò níhìn pẹ̀lú ìgboyà. Ó ní:

> Òwèrè l'à á jà,
> Gbogboo wa.
> Òwèrè l'à á jà,
> Ẹni t'ó yanrí rere kò wọ̀pọ̀.
> Òwèrè l'à á jà,
> Gbogboo wa.

### Ẹsẹ Ẹkaárùn

Aṣẹ̀ṣẹ Ẹwẹ Adó ti ọmọkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ajibọ́lá ni a kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún. Ẹni tí ó bá dá Ifá náà nígbàmí jẹ́ kíló kan tí ń gbé àdúgbò kan ni Ifẹ̀ tí a ń pè ní Ilodè. Wọn kò sọ fún wa idí rẹ̀ tí Ajibọ́lá fi dá Ifá náà, ṣùgbọ́n a gbọ́ pé Ajibọ́lá 'ṣayé ìmí rere' lẹ́hìn tí ó dá Ifá náà fún un tán.

Ohun tí ó dàbí ẹni pé Ọ̀rúnmìlà ń sọ nihìn ni pé ẹni tí a bá dá Ifá yìí fún níbẹ̀rẹ̀ gbé igbésí-ayé rere lẹ́hìn tí ó bá rúbọ tán. Ifá mẹ́ta tí ó parí ẹsẹ yìí ti dámọ̀ràn kí a pé Ọ̀rúnmìlà yóò sọ ayé ọmọ́ràn dì rere gẹ́gẹ́ bí ayé Ajibọ́lá ṣe di rere lẹ́hìn tí ó rúbọ tán.

### Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ń ṣàlàyé pé ẹni tí ó ń ṣe àniyàn ni ọ̀kọ́ọ̀kan nìní ń jẹ́ ẹni tí ń ṣe iku pa ni nígbà mìíràn. Èyí ni kannọ́ ìlà mẹ́ji kọ́kọ́ tí ó sọ pé:

> Mo gbé kí fùjà sìn ọ̀,
> Ní í ṣekú pa bàbàdìnà.
> Mo gbé ọ̀ọ́kẹ́ Ẹnìyàn sìn ọ̀
> Ní í ṣekú páwọn àgbà lẹ́gàn . . .

Ìparí ẹsẹ Ifá yìí mú ààyò nípa ọlà. Àwọn babaláwo t'ó kọ́kọ́ dá Ifá yìí, Ọ̀rúnmìlà ni wọ́n dá a fún. Wọ́n sọ fún Ọ̀rúnmìlà pé yóò di ọlọ́là nínú ọdún náà. Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà rúbọ tán, ó sì rí gẹ́gẹ́ bí àwọn awo ṣẹ̀ ti wí.

Ohun tí Ifá wí ń sọ ni pé ọmọkọ́ni tí a bá dá Ifá yìí fún yóò di ọlọ́là nínú ọdún náà bí ó bá le rúbọ. Ẹni tí a dá Ifá yìí fún ni àwọn ọtá kan tí ó jẹ ẹni tí ó sún mọ́ ọn pẹ́kípẹ́kí. Ifá ń ṣe ìlérí pé yóò ṣẹ́gun àwọn ọtá náà lẹ́yìn tí ó bá rúbọ tán.

### Ẹsẹ Ẹkeje

Nínú ẹsẹ Ifá yìí a rí itàn kan nípa ìṣẹ̀ ọmọ ìwà Yorùbá tí ó jẹ mọ́ ìdẹ. Àwọn awo Ọ̀tà Ifẹ̀ rere ni Obàtálá ọmọ Alára òde Ìlárá sọ fún pé kí wọn ó fi ìdẹ hun agbọ̀n. Gbogbo àwọn ọmọ́ ọmọ ti wọ́n kẹ́sí ni kò lọ́ ṣe ìṣẹ̀ yìí àfi Akinṣàkìn ti í ṣe ọmọ wọn l'òde Ìkirèwè nikan l'ó lè ṣe ìṣẹ̀ yìí.

> Wọ́n náà kési Akinṣàkìn
> Tí í ṣe ọmọ wọn l'òde Ìkirèwè.

> Akinṣàkìn l'ó wáá hun agbọ̀n ìdẹ fún wọn
> L'Ọ̀tà Ifẹ̀ rere.
> Ni wọ́n fi ṣe ayé wọn,
> Ni ayé wọ́n fi gùn gẹ́gẹ́gẹ́.

Ẹsẹ Ifá yìí fi hàn wá pé iṣẹ́ ìdẹ-dídà ti wà lárin ìwà Yorùbá tí pẹ́. Ẹni tí ó bá mọ ìdẹ dà dé ibi kí ó fi hun agbọ̀n wà ní ilẹ̀ Yorùbá ni ayé àtijọ́. Ṣùgbọ́n ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ọ́ pé bí ó bá ṣe àwọn 'awo' tàbí ọmọ ìjìnlẹ̀ ayé àtijọ́ bayìí mọ́ tí ó sún le ṣe iṣẹ́ nìkan tàbí nípa iṣẹ́ ọnà. Ó ní:

> Kò sìwọ nígbà yí mọ́,
> Ọ̀nà Èlọ̀n l'a lè rìnrin dìẹ.

### Ẹsẹ Ẹkẹjọ

Ọ̀rọ̀ nípa orí ni ẹsẹ Ifá yìí náà ń sọ. Ó ní kò sí ẹni tí ó le dá orí burúkú mọ́ pẹ̀lú ojú lásán gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé ẹnìkan kò lè dá ẹsẹ̀ agìwèrè mọ́ lójú-ọ̀nà, tí a kò sì le mọ orí ọ̀kọ́ọ̀ kíníùjọ. Ifá wá sọ pé kí tọkọtaya ó máa ṣe bọ orí wọn ní ọ̀rọ̀ burúkú mọ́ níbití pé a kò mọ ẹni tí ó di ọlọ́là nínú wọn. Ifá parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ nínú ẹsẹ yìí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ pàtàkì. Ó ní:

> Orí tí ó jọba lọ́la,
> Ẹnìkan ò mọ̀.

Ohun tí Ifá ń wí nihìn ni pé a kò gbọdọ̀ sọ pé ẹnìkan kò lè jẹ́ ọ̀kan kan láyé nítorí pé a kò mọ irú orí tí ẹnìkọ̀ọ̀kan mú wáyé. A kò gbọdọ̀ dá 'ìṣẹ̀' ẹnìkan láyé yìí nítorí pé Ọ̀rúnmìlà nìkan l'ó mọ oko̩ rere.

## 11 ÌKÁ MÉJÌ

### Ẹsẹ Ẹkíní

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa ilù Ìká. Ní ilù tí a ń pè ní Ìká yìí, gbogbo àwọn ọ̀ọ̀yàn ibẹ̀ l'ó ń jẹ́ ọmọkọ kìkàkà. Ó bẹ̀rẹ̀ láti orí àwọn babaláwo t'ó dífá fún wọn ní ilù náà tití tí ó fi dé orí Onìkàámògùn, ọmọ afọ̀ṣanyìn ṣẹ̀rìn bọ, tí í ṣe ọba ilù náà. Àwọn babaláwo náà tí jẹ́

'Ẹlẹ́mẹ̀kà, Àjìnàmọ̀kà; Ọ̀ràràbìkàkà, ewé àgbọ̀n ò rọ̀; kókó ki wọn ò rọ̀ ìlẹ̀yà. Ilẹ̀ ni wọ́n ń le bí ọrùn akika, bí ọrùn akika'. Ọba ìlú náà ń jẹ́ Oníkààmògùn. Ifá náà ni ìjòyè pàtàkì kan tí wọn ń pè ní Àrò; ó sì tún ní ìjòyè mìíràn tí wọn ń pè ní Ọlọ́fin.

Ẹsẹ Ifá yìí wá ṣe àlàyé pé gbogbo àwọn ìjòyè ìlú Ìkà wọ̀nyí l'ó ní èèwọ̀ kọ̀ọ̀kan: Àrò Ìkà ki í jajà; Ọlọ́fin Ìkà ki í jàgbò; Oníkààmògùn kì í jẹ òwúkọ. Látì ìbí ọ̀rọ̀ èèwọ̀ yí ni ẹsẹ Ifá náà ti ré mọ́ ọ̀rọ̀ kókó ti wọn ń kà ọ̀gbọ́ọ̀ àti awòsá wọn lọ ní ìlú Ìkà. Wọ́n kìlọ̀ fún àwọn tí ó kò èsè náà, ṣùgbọ́n wọn ò fẹ́.

Ẹsẹ Ifá yìí tún wáà padà sí ìbi ọ̀rọ̀kọ kàakàa tí wọn ń jẹ́ ní ode Ìkà. 'Ìpọ̀npọ̀dè-tàgbà ìlẹ̀ l'ó ń jẹ́ orúkọ kàakàa: 'Ìyà l'Akàagun; bobo ni Akàagùn; èyí tí wọ́n ń pọ̀n lẹ́hìn ni Akàakàagbasà'. Ẹsẹ Ifá náà padà sí ìbi wí pé èèyàn ìlẹ̀ ni àwọn ará òde Ìkà nítorí pé wọ́n fẹ́ràn láti máa fi orí ọkà bọ̀mú. Ìrumọ̀ èyí ni wí pé wọ́n fẹ́ràn láti máa fa ìjàngbọ̀n lọ́ọ̀.

Látì òkè tití dé ìparí ẹsẹ Ifá yìí, ìfọ̀rọ̀ṣìrè ni gbogbo ọ̀rọ̀ ìbẹ̀. Ẹsẹ Ifá yìí ń fi orìṣìríṣìí gbólóhùn ṣìrè nìbí. Gbogbo àwọn gbólóhùn náà l'ó wá dá l'orí sílébù ẹyọ kan ṣoṣo, èyí ni 'kò'. Bí a ṣe ń pe sílébù yìí ni ó ń gbé ohùn lọ sókè sódò bí a ṣe ń fi ṣìrè. Èyí l'ó jẹ́ ki gbogbo ọ̀rọ̀ ẹsẹ Ifá náà ó máa dùn kàakàa. Ṣe Ìkà tilẹ̀ ni orúkọ Odù náà, èrò ìfọ̀rọ̀ṣìrè báyìí, pàápàá tí a tí ń mú sílébù kan tàbí méjì lára orúkọ Odù tí a sì ń ṣọ̀rọ̀ ẹ̀gẹ̀ẹ̀gẹ̀ nínú ẹsẹ Odù náà láti fi orúkọ náà ṣìrè̀ wọ́pọ̀ nínú ẹsẹ Ifá.

Lóòtọ̀ ìfọ̀rọ̀ṣìrè ni pàtàkì nhan tí Ifá ń fi lédè nínú Odù yí, ṣùgbọ́n síbẹ̀síbẹ̀, Ifá tún ń sọ nǹkan díẹ̀ nípa ìlú Ìkà. Ifá yìí jẹ́ ìkà tí wọn ti ń jẹ oyè Àrò àti Ọlọ́fin tí í ṣe oyè àwọn Ọ̀gbóni. Ifá náà sì jẹ́ẹ̀lú tí ìmọ̀ Ifá tí gbilẹ̀ nítorí pé gbogbo àwọn ìjòyè tí a dárúkọ nìbẹ̀ l'ó tì tẹ Ifá. Ìlú Ìkà tún jẹ́ ìbi tí wọn tí ń ṣègbẹ́ dáadáa, tí wọn ń gbìn ìgbọ̀ọ̀ àti awòsá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn a máa kó araa wọn ní nǹkan lọ nínú oko.

## Ẹsẹ Ẹ̀keji

Ọ̀gọ̀ọ̀ ìfọ̀rọ̀ṣìrè l'ó pe nínú ẹsẹ Ifá yìí nìbí tí a gbé ó fi sílébù kan l'ára orúkọ Odù Ìkà ṣerè. Sílébù yìí ni 'kà' tí a fi dárà kàakiri àwọn ìlà tí ó bẹ nínú ẹsẹ Ifá yìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni ọ̀rọ̀ tí ó bẹ̀rẹ̀ tàbí tí ó pari pẹ̀lú 'kà' nínú ẹsẹ Ifá yìí. Nígbà míràn a yí ohùn tí a fi pe sílébù yìí padà láti ọ̀rọ̀ kan dé èkèjì. Èyí l'ó fà á tí a fi ní ọ̀rọ̀ bí àkà, òkèrà àti ìkorahun nìbi tí sílébù kan náà yí tí ní ohùn òkè, ohùn ìsàlẹ̀ àti ohùn àárín.



Ẹsẹ Ifá yìí kò dúró lórí ìfọ̀rọ̀ṣìrè nìkan. Pàtàkì ọ̀rọ̀ tí ó bẹ nínú ẹsẹ Ifá náà dá lórí Ṣàngó. Odù Ṣàngó ni Odù yí. Òhun ti ẹsẹ Ifá yìí sì ń fi yé wa ni ìrà ìpìlẹ̀ àti ara-àìlẹ́ẹ̀ òrìṣà Ṣàngó. Ẹsẹ Ifá yìí wá sọ pé jagunjagun ni Ṣàngó. Ó ní 'òkòkòńkò, ta l'ó le bá Ṣàngó kògun?' Èléyìí fi hàn bí Ṣàngó ṣe kó orìṣìríṣìí ìlú nígbà tí ó fi wà láyé.

Ẹsẹ Ifá yìí tẹ̀ka sí i wí pé Ṣàngó a máa fún ní lọ́ọ̀mọ bí a bá ń rìn ìn. Ẹsẹ náà sọ wí pé bí Ṣàngó ṣe bawí tó ni ní dé ìbi pé a lè kò á sí éèmọ̀, síbẹ̀síbẹ̀ ó lààmú àwọn tí ó gbọ́kẹ̀ lé e, a sì máa fún wọn lọ́mọ.

Ẹsẹ Ifá yìí tún sọ wí pé Ṣàngó kò fẹ́ràn èké rárá. Ó ní 'ó bámi kunlẹ̀ èké lókè Agùnpopo, ó fàgbòrí la ilẹ̀ èké kààkàà'. Ẹsẹ Ifá náà tún wá sọ díẹ̀ nínú orúkọ Ṣàngó fún wa. Òun ni a ń pè ní 'Àlégorùng àti Alégorìyè'.

Nípa ìwà ìpìlẹ̀ Ṣàngó, ẹsẹ Ifá náà sọ̀rọ̀ bí ọjọ́ kan tí Ṣàngó gbé ẹ̀lọ̀ kaná sí ilé ànà rẹ̀, tí ó sì kun ìgbà rẹ̀ṣẹ̀. Àwọn àna Ṣàngó fẹ̀rẹ̀ gba ọmọ wọn lọ́wọ́ rẹ̀. Ṣàngó wá ẹ̀bẹ̀bẹ̀ yán sí àwọn ànà rẹ̀, kò rí nítorí pé kò sí ẹni tí ó le dáhùn dé é dé ìbi wí pé yóò ṣe onípẹ̀ fún un.

Wàyí o, a nílàti rántí pé Ọlọ́fin ni a kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún. Ó dàbí ẹni pé Odùduwà tí í ṣe Ọlọ́fin àkọ́kọ́ ni a dá Ifá yìí fún nítorí pé ẹsẹ Ifá náà pè é ní:

> Ọlọ́fin, orí ogbò,
> Ọlọ́fin kaakaa wáá.

Odùduwà ni Ọlọ́fin tí a mọ̀ pé ó gbó láyé tó báyìí. Òun ni ẹsẹ Ifá mìíràn sọ wí pé ó gbó gbóó gbó, ó sì dọ̀ta mọ́ wọn lọ́wọ́.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí sọ wí pé kí ó fetísílẹ̀ nítorí pé bí ọ̀jọ̀ bá ń rọ̀, ẹyẹ oko kì í kú, bí ẹyẹ àjọ̀ bá sì gbóde, ẹyẹkẹyẹ yòókù kò gbọdọ̀ tún ké mọ́. Ìbẹ̀ náà sì ní àwọn ẹyẹ oko ṣe máa ń dákẹ́ nígbà tí àdìn bá ń ṣe kàtàkàtà. Àkiyèsí pàtàkì ni Ifá ṣe nílùúin nípa ìwà àwọn ẹyẹ.

Ẹsẹ Ifá yìí tún wá tí ìbi àkiyèsí pàtàkì yí nípa àwọn ẹyẹ njó ọrun ré mọ́ ọ̀rọ̀ nípa àwọn mẹ́ta kan tí ó fẹ́ẹ́ kú. Kò sọ ẹ̀ni náà tí ó fi fẹ́ kí àwọn mẹ́ta náà: Wìngbàlù, ọmọ wọn n'ílé Alárá; Òrìṣàtálàbí, ọmọ wọn lóde Ìjìgbò; àti Ẹ̀rìgìnbìyìí, ọmọ Olóponlà Ọ̀gbèjà.

Ìgbèsọ̀ kẹta nínú ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ oríkì Ọ̀rúnmìlà. Ó pe Ifá ní ọmọ ẹran ṣiìrí tí í yẹ ọdẹ lóko. Ṣe ọdẹ l'ó ń pa ẹran lóko, nítorí náà ṣìrí ẹran l'ó yẹ é, ekiri ẹran kékeré kò yẹ é. Ọ̀rúnmìlà náà ni a tún

pé ní ọmọ lọ́ fọ̀ tí í fọ dìdùn Ifẹ̀gùn. Ṣé Ọ̀rúnmìlà a máa fọ Tápà àti Ẹ̀gùn. Lílì níyì tí a fi ń pè é ní afèdèfẹ́yọ̀.

Ìgbésẹ̀ tí ó parí ẹsẹ Ifá yìí sọ ní pé nígbà tí a kọ̀lù alẹ̀ a kò rí omijé, apẹ̀ ni a kò sínú ilé fún ọmọ ẹlẹ́ṣẹ̀. Ọ̀rọ̀ nípa Ifá náà ni a tún sọ dé ibi gbẹ̀du àti àrán tí a ń lù fún àwọn ọba. Gbẹ̀du jẹ́ ìlù tí a ń lù fún àwọn ọba, àrán sì jẹ́ ìlù tí a ń lù fún àwọn babaláwo. Àmì kan náà yí ni ó ń pè ní ìpèsè. Ẹsẹ Ifá yìí wá béèrè lílì rẹ̀ tí a kò fi rí omijé nígbà tí Ọlọ́run ń lu ìpèsè. Ìlẹ̀ sì ni ìlù ọ̀dọ̀ ni ìpèsè. Ẹsẹ Ifá náà wáá sọ wí pé:

Bí a ti dá yíì tán ni a dá erin.
Bí a ti dá Jẹ̀yẹ̀ tán ni a dá Odùdúwà.

Ìlùyà ìlàbẹ̀ sìjò nígbà tí Ọlọ́run ń lu ìpèsè yí náà l'ó fà á tí tọmọ-dìtàgbà fi á máa kú nọ́. Nígbà tí ó yà tí wọ́n tí ó bó bayìí, ni wọ́n tó wá bẹ̀rẹ̀ sí í jó.

Ọmọ kékeré, wọ́n jó wẹ́lẹwẹ̀lẹ.
Àgbàlagbà ń fọpá ọ̀rẹ̀rẹ̀ bolẹ̀.

Ẹsẹ Ifá yìí ó tún sí ìgbà tí ó fi jẹ́ wí pé apẹ̀ ní àwọn babaláwo máa ń jó dìpò ìpèsè ti Olódùmarè fúnra rẹ̀ sẹ̀ ti lù. Nítorí náà, a lè sọ wí pé ìlù Olódùmarè ni ìpèsè. Ìlù yẹ̀ ni, ẹni tí ó ni í jó o, ẹni tí ó ni í sì í lù ú pẹ̀lú. Kí í ṣe ìlù tí a lè máa lù fún tajátẹran. Nígbà tí àwọn ènìà kò kọ́kọ́ jó ìpèsè ti Olódùmarè ń lù ni ikú fi pa gbogbo ọmọdé àti àgbà. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó yá, àwọn babaláwo mọ ìyí ìpèsè. Bí ọmọdé tí ń jó wẹ̀lẹwẹ̀lẹ nígbà tí a ń lu àrán ni àwọn àgbà awo ń fi ìrẹ̀ ọ̀pá ọ̀rẹ̀rẹ̀ sọlẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ nípa nípa babaláwo kan tí máa gbọ́ ti Ọ̀rúnmìlà kíní nígbà gbogbo nínú orí ìkúnlẹ̀ ẹ̀wù. Bí afẹ́fẹ́ bá ń fẹ́, bí òjò ń rọ̀ sìmìsìmì, bí òòrùn ń ràn, babaláwo náà máa gbọ́ Ifá kíkíkí ni. Nígbà míràn pẹ̀lú ẹlẹ́ẹ̀lẹ́ ni babaláwo fi ń sin Ọ̀rúnmìlà.

Ẹsẹ Ifá yìí wá sọ pé nǹkan tí babaláwo ń béèrè fún ni pé kí Ifá ó ṣe tùtù sáyé òun. Èyí ni pé kí ó jẹ́ kí ayé òun ó tù, kí ó bà, kí ó sì tòrò nìnì. Babaláwo sì tún ń tọrọ pé kí Ifá ó ṣe ìwọ̀n àkúfọ́ǹjọ̀ọ̀rì fún òun bí ó ti ṣe fún Ọ̀wà, Ọ̀gà, Ògìrì gbẹ̀du.

Àkúfọ́ǹjọ̀ọ̀rì nikan ó tó bí ọmọ ó bá gbọ́ngbọ́n mọ́n. Ó ní:

Nígbà tí mo bá kú,
Ọmọ ni kí ó jẹ́ kí
Ó fọpin rẹ̀ mí lóri dandandan.



Ìtumọ̀ gbogbo èyí ni pé kò sí ẹni kan tí àwọn babaláwo ń wá nǹkan láàlà wọ́n fún Ifá àti kí ayé wọ́n ó dára, kí wọ́n ó bà ikú tete, kí ọmọ rere ó sì gbẹ̀hìn wọ́n. Wọ́n kò béèrè owó, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ò béèrè aṣọ. Ìgbẹ̀hìn, èyí tí afáyà máa ń lèpa, ni àwọn olùfọkànsìn yí ń dá.

## Ẹsẹ Ẹ̀kaàrùn

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn kan nípa ìlú Ìkà. Ọba ìlú yìí tí a ń pè ní Onikáàmigún, ọmọ akúwọ́ráká ìmú ẹ̀ṣu, kò ní ọbìnrin. L'ó wá lọ sunkún bá àwọn 'Igun ṣọ̀ ni í l'orígun ìgunn ilé', àwọn 'Sìdìdì ni í dábí ẹran òwú', awo ni wọ́n. Wọ́n ka ẹbọ fún Onikáàmigún; ó sì rúbọ. Lẹ́hìn tí ó rúbọ tán, ó sì bímọ.

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ìwúrẹ̀ aya. Ẹni tí a dá Ifá náà fún ní lààtí jẹ́ ẹ̀kèjìn pàtàkì bí ọba tàbí ìjòyè; ṣùgbọ́n olùwarẹ̀ ó fẹ́ya. Bí ó bá le rúbọ bí Onikáàmigún yóò níí aya.

Dẹ́rẹ̀ ẹsẹ Ifá náà tí í ṣe oríkì àwọn olúwo tí ó lọ dá Ifá náà jẹ́ ìkìlọ̀ pàtàkì nípa ìgun ṣọ̀ àti igun ilé. Ifá sọ wí pé nígbà yí jẹ ara wọ́n gẹ́gẹ́ bí sìdìdì ti dà bí ẹran òwú. Àwọn àwòrí ìsọ̀nyí dára púpọ̀ nítorí pé bí Ifá ṣe ṣe àpèjúwe àti àlàyé wọ́n náà ni wọ́n rí bẹ́ẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí jàmùjàmù 'tí yóò mú dá ọmọ ní gbì lọ́gànjọ́'. Ifá wá ń pààṣẹ fún jàmùjàmù pé kí ó dẹ̀rù, kí ó máa lọ nítorí pé àgbàlagbà papàá tóó bẹ̀rù. Ìyàlẹ́ ẹsẹ Ifá yìí wá jẹ́ ọ̀rọ̀ tí Ifá fi lé jàmùjàmù lọ. Ifá ní nítorí pé ọjọ́ọ́ ni baálẹ̀ bá Èṣù, nítorí pé abẹ̀ọ̀gùn kì í kú sójú Ẹ́gùn, dọ̀kọdọ̀kọ kì í sì í kú sójú okó, kí jàmùjàmù ó dẹ̀rù, kó máa pàra lọ.

Ó dàbí ẹni pé ẹni tí a pè ní jàmùjàmù yìí, ìdàmú ni. Wọ́n wá lọ bẹ Ifá lọ́wọ̀ pé kí ó bá àwọn lé e lọ. Ọ̀rọ̀ tí Ifá fi lé e lọ l'ó wà ní òkè yí. Ohun tí Ifá ń sọ nihìn ni pé bí ó bá ṣe pé nǹkan kan ń dẹ́rùbà ẹ̀nìyàn l'ógànjọ́ òru, kí ó lọ rúbọ kí ó sì dì mọ́ Ọ̀rúnmìlà kí ó bá a lé ohun ẹ̀rù náà lọ. Ohun ẹ̀rù kàn ni ìdàmú náà, kò ní í lè ṣe àgbà ní nǹkan nítorí pé àgbàlagbà pàápàá ti dì ẹ̀rù.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ẹsẹ yìí sì sọ̀rọ̀ nípa ọ̀tá. Ẹni tí a dá Ifá yìí fún, ọ̀tá pọ̀ fún olùwarẹ̀. Ṣùgbọ́n wọ́n ò ní í ṣe é ní nǹkan kan gẹ́gẹ́ bí ìgbà àwọn ọ̀tá ó ṣe kò òkè tí ó bọ̀ láàrin ọ̀tá, t'ó tún lé gbanyìngbanyìn. Òkè ni Ifá ń pè ní ẹni ayé ó kì. Ó ní:

Ẹni apá ó ká
Ni ọmọ ó á pọkẹ́.
Ogún ọdún òní o,
Òkè ó bẹ lókè gbọngbọn.
Gbọngbọn ni tòkè.
Òkè, òkè gbọngbọn.

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ṣe àkíyèsí pàtàkì nípa orìṣà mẹ́ta. Ifá ní bí aja bá gbó lóko, ìgbe wọn ni í dédé. Èyí fi hàn wí pé oko a máa jìnnà díẹ̀ sí ilé ṣé ilé wí pé a kò lè gbọ́ ìgbe ajá tí ń gbó lóko ní ilé. Ifá tún sọ wí pé apájùbà kò mọ ilẹ̀ ọrọ̀. Òtítọ́ gbáà ni eléyìí nítorí pé ọnikan kìí lè sọ bí àjùbà tí í ṣe ilẹ̀ tómù tí a pa yóò mú èso mélé wá. Ọjọ́ ìnú ikọ̀kọ̀ ni a fi ń mọ àjùbà tí a pa lóko tí a sì á fi ìgbàgbọ́ gbé e pé yóò gba nǹkan tí a gbìn síbẹ̀. A kò lè sọ pàtó bí ọrọ̀ náà ó ti rí, àfi ìgbà tí a bá dán an wò.

Ifá tún wáá sọ wí pé ojú abẹ́ẹ̀rẹ̀ ò tóbi inú rẹ̀. Ṣé òtítọ́ ha kọ́ ni èyí náà?

Ẹsẹ Ẹkẹ́ta

Ọ̀rọ̀ nípa àìrọ́bọ àti àìtètè rúbọ ni ẹsẹ Ifá yìí ń sọ. Àwọn babaláwo l'ó dá Ifá fún Olúwẹ̀ẹ̀rẹ̀, ọba ìlú Ìwẹ̀rẹ̀. Wọ́n sọ fún un pé kí ó rúbọ kí ó mọ bàá pàdé ikú lójú-ọ̀nà. Ṣùgbọ́n Olúwẹ̀ẹ̀rẹ̀ kò tètè rúbọ. Kí ó tó wí pé yóò rúbọ náà, ó ti pàdé ikú lójú-ọ̀na, ó ṣe bẹ́ẹ̀, ó bákú lọ.

Ifá wá sọ wí pé kò sí ìyàtọ̀ láàrin aláìrúbọ àti àwọn tí kò tètè rú. Nítorí náà kíákíá l'ó yẹ kí ẹnìyàn ó tètè máa rúbọ nígbà ìgbà tí ọnikan kò lè sọ àkókò tí àwọn ajogun ó dédé. Ifá a kò bá tii rúbọ tí ajogun fi dé, kò ní í sí ohun tí a ó tí síwájú fún ìpàdé ẹni ara yóò.

## 12 ÒTÚÚRÚPÒN MÉJÌ

Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Ẹsẹ Ifá yìí ṣe àlàyé wí pé àwọn ajogun ńlá mẹ́rìẹ̀rìí tí a ń pè ní ikú àti àrùn jẹ àkápò fún Ọ̀rúnmìlà nígbà kan rí. Ọ̀rúnmìlà fúnra ara rẹ̀ l'ó tẹ ikú nífá, tí ó sì fi àrùn ṣe Ọ̀jàgbọ̀nà. Òyè pàtàkì ni oyè Ọ̀jàgbọ̀nà láàrin àwọn babaláwo. Ìdí nìyí tí a fi máa ń wí pé:



Ifi a bá wọ̀lú,
Olúwo l'à á kọ́ọ́ kíí si;
Ọ̀dọ̀ Ọ̀jàgbọ̀nà l'à á bèèrè.

Babaláwo wá ń sọ nǹkan pé bí ó bá ṣe wí pé òótọ́ ni Ọ̀rúnmìlà tẹ ikú nífá, tí ó sì fi àrùn jẹ Ọ̀jàgbọ̀nà, a jẹ́ wí pé kí babaláwo ó máa kápò fún àwọn ajogun wọ̀nyí l'ó kù o.

Pàtàkì ohun tí Ifá ń wí nínú ni wí pé kò yẹ kí babaláwo ó máa bẹ̀rù ikú àti àrùn nítorí pé àwọn ni àwọn náà. Ìdí mìíràn tí babaláwo kò fi gbọ́dọ̀ bẹ̀rù àwọn ajogun ni wí pé ọmọ ọ̀dọ̀ Èṣù ni gbogbo wọn.

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí tí í ṣe oríkì àwọn olúwo tí ó dá Ifá náà jẹ àkíyèsí nípa bí ahọ́n ṣe máa ń ṣe igi ọkọ bí igi àgbọn, tí ó máa ń yọ ewé wọn yígbanyìgbọ. Ifá tún ṣe àkíyèsí nípa àwọn ọranko mẹ́jì tí a ń pè ní èṣúrú, bí wọn ṣe máa ń yí ara wọn sílùùn, gbọ̀ọ́mù nígbà tí wọn bá ń jà. Tàkọ̀tabo àwọn ọranko tí a ń pè ní èṣúrú yì l'ó máa ń jà lákọ̀n lákọ̀n.

Ẹsẹ Ẹkẹ́jì

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí Oyèépolú, ọmọ Ìwàrẹ̀fà nílẹ̀, tí baba ìní tirẹ̀ tí kú nígbà tí ó fi wà ní kékeré. Baba Oyèépolú yìí ní í máa bá wọn ṣorò gbogbo ní Ilẹ̀. Nígbà tí baba náà kú tán, kò sí ẹni tí ó kọ́ọ́ Oyèépolú nípa orò-ṣíṣe mọ́. Nígbà tí Oyèépolú dàgbà tán, tí wọn kò ohun orò sílẹ̀, l'ó bá bú pùrú sẹ́kún. Ó ní òun ó mọ̀kan. Bí ọ̀rọ̀ tàbí ohì ni wọ́n kọ́ ta sílẹ̀ ní òun ó mọ̀. Ní ìparí, ẹsẹ Ifá náà wí rọ àwọn ìgbèsì ọ̀run láti sọ̀rọ̀ wá gba orò náà ṣe.

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí jẹ àkíyèsí nípa oríṣiríṣi nǹkan. Pẹ̀pẹ́ tàbí pẹ̀pẹ̀lẹ̀ tí a máa ń fi jókòó jẹ ohun tí ó máa ń gbé inú ilé. Ìdí nìyí tí ó fi pè é ní awo ilé. Òtítà tàbí àpótí tí a máa ń gbé kiri ni a sì máa ń fi jókòó ní ìta. Ifá tún wá ṣe àkíyèsí nípa alápàándẹ̀dẹ̀. Ó ní ilé alápàándẹ̀dẹ̀ ò kanmí, bẹ́ẹ̀ ni kò kan ìkọ́, ojú-ilé rẹ̀ sì ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bàyìí. Ìtọ́ni ohun tí Ifá ń wí nípa tí àìwè ojú-ilé alápàándẹ̀dẹ̀ yì ni pé ayé tí dorí kodò.

Ní ìkẹ́hìn, Ifá ń sọ nǹkan pé ayé tí dojúdé. Gbogbo orò àti ààwẹ̀ ilẹ̀ wa ni a kò mọ̀ mọ́. Àfi kí àwọn baba ńlá wa tí ó ti dé Ìkọ̀lé-ọ̀run ó tún wá kọ́ wa láti ṣe orò tún ayé ṣe.

Ẹsẹ Ẹkẹ́ta

Ọ̀rọ̀ nípa ọ̀gbọ́n ni ẹsẹ Ifá yìí ń bẹ̀rẹ̀. Odù Òtúúrúpọ̀n jẹ Odù kan tí ó hùn fún ọ̀rọ̀ nípa ọ̀gbọ́n. Ìdí nìyí tí a fi ń ṣe Odù yìí ní

Ọlọgbọn 'Mọ̀jì. Orúkọ àwọn ọ̀lọ́run tí ó dá Ifá yìí nọ wí pé ọgbọ́n tí ọlọgbọ́n ni 'mọ̀ lí ó fi ń jẹun. Ó tún sọ wí pé ẹ̀pínẹ̀rẹ̀ ẹ̀yin kò lè mọ bí yóò ṣe gba ìmọ̀ràn orun rẹ̀. Àwọn ọ̀lọ́run t'ó ń fi nǹkan wọ́ọ̀yì jẹ́ nǹkọ l'ó wà dá Ifá fún Ọ̀rúnmìlà nígbà t'ó ń lọ mú'lẹ̀ tí yóò dúró sí. Lẹ́hìn, oko Ọ̀rúnmìlà wá pọ̀ ọ̀gẹ̀dẹ̀ bí odù t'ó ń gbé lọ.

Ohun tí ẹsẹ Ifá yìí fi wá pari rẹ̀ wí pé gbogbo nǹkan tí Àgbọnìrè-gún bá ṣe ni kí wọn ó máa fi hùn un. Ó wá fi ọ̀rọ̀ parí ọ̀rọ̀ náà; èyí l'ó ní sọ ẹsẹ Ifá yìí di òògùn ìṣegbé. Ìdí rèé tí ẹsẹ náà fi parí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ nípa ọ̀lọ̀un. Ó ní ẹni tí a bá dá Ifá yìí fún, bí ó bá ṣe wí pé ó fi ṣe ohun bábùrù kan, wọn ó fi hùn un ni. Ohun 'bàbùrù náà kò ní í lè hun ún mọ́. Ó ní

Mo fi ewé ohun,
Mo fi se ohun jẹ,
Ohun burúkú kì yóò kò hun mí.
Ewé ọ̀rọ̀, wọn kì í hunlẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Akíyèsí nípa ewé àti akítì ni ẹsẹ Ifá yìí fi bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀. Ó ní akítì fi dìin jẹ ewé, ọgbọ́n iyàtọ̀ t'ó wà láàrin àwọn mejeeji ni wí pé akítì kò lè mọ rírí bí ewé. Ifá tún wá ṣe àkíyèsí pé bí ọ̀jọ̀lọ́ bá ń fa ìgúnrí gbogbo ara rẹ̀ a máa dàn gbinrin, tí yóò sì tún máa kọ nàmà.

Ẹsẹ Ifá yìí wá dá lórí ẹnìkan tí a ń pè ní *Arúyẹ̀rọ̀pọn* tí kò ní ilé. Nípa bí ìwà ó ṣe di onílé ni Arúyẹ̀rọ̀pọn dífá sí. A kò sọ fún wa ìmọ̀ràn tí àwọn babaláwo fún Arúyẹ̀rọ̀pọn ní ọjọ́ náà. Ifá wá parí ẹsẹ rẹ̀ pẹ̀lú àkíyèsí nípa ọgbọ́n tí ó máa ń kọ́ ilé tirẹ̀ sí inú ilé onílé. Ó jẹ́ bí ẹni wí pé Ifá ń fi ọ̀kàn Arúyẹ̀rọ̀pọn balẹ̀ ní lílọ wí pé yóò di onílé bí ó tilẹ̀ ṣe wí pé ilé ọlọ́mìràn ni ó máa ń gégé bíi tirẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀karùn

Ọ̀rọ̀ nípa ìrẹ̀ ọmọ ni Ifá ń sọ nihiin. Ifá ń sọ wí pé ẹni tí a kì ẹsẹ Ifá yìí fún yóò bímọ dandan. Ifá wá fi àpẹẹrẹ orógbó, ìgbàlẹ̀ yọn àti ṣẹ̀ṣẹ̀ẹ̀gidi kan ìṣe rẹ̀ múlẹ̀. Ifá ń sọ nihiin wí pé nhọ̀ọ̀n ìgbà tí orógbó tí kò tíì fẹ́ ẹ̀rẹ̀ bá ti ń bímọ, tí ọmọ ìgbàlẹ̀yọn kò sí lóńkà, tí ó sì jẹ́ wí pé a kì í fẹ́ ọmọ kù lẹ́hìn ṣẹ̀ṣẹ̀ẹ̀gidi, dandan ni kí oníbèèrè náà ó bímọ. Ifá wá fi aládìí ṣe àpẹẹrẹ ní ìgbẹ̀hìn ẹsẹ yìí.



Aládìí jẹ́ ikú fún àwọn ìdèrà. Ifá wá ń sọ wí pé bí aládìí kì í ti í fẹ́ ọmọ wẹ́wẹ́ kù, nígbà kan ni ẹni tí a dá Ifá yìí fún kò ṣe ní í fẹ́ ọmọ wẹ́wẹ́ kù l'áyé rẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ yìí, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa ayé. Ó ní ohun tí a ń pè ní ayé gan-an kì í ṣe ohun tí a kò fi ojú kàn án rí. Ojú inú ni a ó máa fi wò ó. Nítorí náà bí a bá sọ wí pé ayé l'ó ń ṣe ẹnìkan, a kò lè rí ayé tí ń ṣe é náà, ìrírí ni a ó máa wò láàrin, a kò ní ayé rí.

Ẹsẹ Ifá yìí tún dá lórí ẹni tí kò bímọ tàbí tí kò lówóyàn. Ifá ń sọ wí pé bí ó ṣe jẹ́ wí pé àtàn ni òpòlopọ̀ ẹ̀yàn, tí ọmọ tí ayé bí kò sí lóńkà, dandan ni kí ẹni tí a dá Ifá yìí fún ó dọlọ́mọ.

Ẹsẹ Ifá yìí sì tún ń sọ nípa ọ̀run ẹni. Ifá sọ wí pé bí ó bá ṣe wí pé ẹlẹ́yìí kò lẹ́nìkan, kí ó mára, kí ó bọ ọ̀run rẹ̀ kí ó lè baà dọlọ́mọ. Kí ó fi àgbọ̀n àti ẹyinlà bọ ọ́.

Ẹni tí a kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún ni à ń pè ní Gbogbolohun. Ìgbà tí a dá Ifá náà fún un ni ọjọ́ tí ń ṣawo lọ sí ìlú jìjìn nítorí lórí ooni. Ifá sọ wí pé bí ó bá ṣe wí pé oníbèèrè yí ń lọ sí ẹ̀yìn-odi l'ó fi dáàbò, kí ó sọ fún un wí pé gẹ́gẹ́ bí Gbogbolohun ṣe lọ sí àjò ọ̀kun, ìlà ọ̀sà, tí ó sì bọ̀ láyọ̀, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ẹlẹ́yìí ó ṣe lọ gbooro, tí ó sì bọ̀ gboorọ.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ìrìgbọ̀n. Ifá ń ṣe àkíyèsí pé ọgbọ́n a máa pa ní ìbẹ̀rẹ̀ bí a kò bá mọ ọ̀n lò. Ẹni tí ọgbọ́n bá sì pa ìbẹ̀rẹ̀, ọlọ́mọràn ó gbọ́n nù-un. Ní ìdí àìgbọ́n ni ọgbọ́n gbé pa wọ́n fún bí abẹ.

Ifá tún ṣe àkíyèsí ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ yìí pé àgbàlagbà nǹkan kò lè e rí ìdí ọgbọ́n. Ó wá fi ìkosùn arúgbó àti ògòdò ṣe àpẹẹrẹ. Ó ní bí arúgbó bá kosùn tán, à á fi èyí tó kù lọ̀ rẹ̀ pa inú, ṣùgbọ́n b'ó bá ṣe ògòdò tàbí ọ̀kọ̀ yóò bàa fi osùn ra ara wọ́n wọ́n lásán ni.

Ní ìparí, ẹsẹ Ifá ń tọ́ka sí àwọ̀ Ifá. Ó ní ohun tí Ifá bá wí bí í pẹ́ tí ó fi ń ṣẹ. Ifá pàpà ni a tilẹ̀ ń pè ní aláṣẹ tàbí 'ọlọ́ràn àṣẹ'.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ọ̀tẹ̀ Òòṣàlá kan tí ó lọ bọ Òòṣà náà ní ilé kan. Wọ́n ka ẹbọ fún ọlọ́mọ Òòṣà, ó sì rúbọ. Ṣé ojú l'ó ń pọ́n an tẹ́lẹ̀. Ìgbà tí ó dé ibi t'ó ń lọ, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í ní ṣe àṣẹ́ṣẹ́ tírí tí ó fi dàbí.

Nítorí tí Ifá ń sọ fún wa nínú ẹsẹ yìí pé ẹnikẹ́ni tí ojú bá ń pọ́n ní ìgbà kan tí ó bá ní sùúrù, kò yẹ kí ó fi ara sílẹ̀ rí ẹni tí ń kú nítorí ìgbà rẹ̀ tí ó gbọ́n dáadáa. Ohun tí ẹsẹ Ifá yìí fi parí ni wí pé bí ó tilẹ̀ burú burú fún babaláwo, a kò kọ̀ fi wọ́ ìgbẹ̀rì.

# 13 ÒTÚÁ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ekínní

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí Odidẹrẹ́ àti Àgbọnmìrègún. Ọ̀rúnmìlà náà ni a tún máa ń pè ní Àgbọnmìrègún. Nípa odidẹrẹ́, Ifá sọ wí pé aya Ọ̀rúnmìlà ni ẹyẹ yìí. Ifá wá sọ bí odidẹrẹ́ ṣe máa ń dàbùn nígbà tí wọ́n bá bí i lójú ọkọ rẹ̀. Odidẹrẹ́ a máa pe ọkọ rẹ̀ ní ọkùnrin dúdú òkè Ìgẹ̀tì. A sì tún máa pè é ní ọmọ àdó bàbà tí í wẹ̀wù ológún. Ohun tí Ifá ń sọ fún ọmọbìnrin yí ni wí pé olùwarẹ̀ ó níí ayà kan tí ó fẹ́ràn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí odidẹrẹ́ ṣe fẹ́ràn Ọ̀rúnmìlà.

Ẹsẹ Ifá yìí sì tún dá lórí igi ọsè. Ifá ń sọ fún wa wí pé nínú ìgbà tí ó ń jẹ́ wí pé Ṣàngó kì í pa igi ọsè, tí mà kì í jó o, kò sí ohun tí àwọn ọ̀tá rẹ̀ lè fi ṣe. Ifá ń sọ fún ọmọbìnrin yí pé láéláé ni wọ́n ń pariwo orúkọ rẹ̀, àwọn ọ̀tá kò ní í lè rí i gbé ṣe.

## Ẹsẹ Èkejì

Nínú ẹsẹ yìí, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn Ìmọ̀le. O kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ nípa ìrò aṣọ tí wọ́n ń wọ̀. O pè wọ́n ní 'Bàbá Mọ̀le, abẹ̀wù gẹ̀rẹ̀jẹ̀'. O tún wá ṣe àlàyé wí pé àwọn Ìmọ̀le a máa bímọ ìbejì. Ní Ifá fi pe Bàbá Mọ̀le ní:

Òrúnrìnrà, a ní ìbejì sìnà ilé ràá.
A tú ìbejì sìnà oko gbẹ̀ranṣẹ̀ẹ̀.
Bí wọ́n tí ń bí nílé,
Ni wọ́n ń bí lóko.

Odù Òtúá Méjì gan-an ni à ń pè ní Bàbá Mọ̀le nítorí pé òun l'ó ya ilàn àwọn Ìmọ̀le. Nítorí, Ifá ń sọ fún wa wí pé ẹni tí ó dá Òtúá Méjì, olùwarẹ̀ jẹ́ ẹni tí yóò bí ọmọ púpọ̀. Ifá sọ wí pé òun rìn ìbejì nàkì tí a gbé dá Òtúá Méjì. Èyí ni Ifá ń sọ nígbà tí ó wí pé 'Òtúá tí ń tú ìbejì sìnà ilé ràá.'



Ní ìparí, Ifá náà wá sọ wí pé àwọn Ìmọ̀le kò mọ awo. Èyí l'ó fà á tí wọ́n ó fi lè rí awo.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ẹsẹ Ifá yìí náà tún dá lórí àwọn Ìmọ̀le. Ifá ń sọ nínú pé ọ̀kẹ́ ni àwọn Ìmọ̀le fẹ́ràn láti máa jẹ. Ifá tún ṣe àlàyé pé lẹ́hìn ìgbà tí Ìmọ̀le rúbọ tán, tí ẹbọ rẹ̀ sì dà tán, l'ó di wí pé ó bẹ̀rẹ̀ sí í jẹ ohun gbogbo ní ọ̀fẹ́. Ifá wá fi hàn àwọn Ìmọ̀le nípa ìmọ̀ràn yìí wí pé ìgbà tí ó máa ń jẹ ẹbọ lọ́fẹ̀ẹ́, àkókò náà gbà l'ó ń jẹ òkú lọ́fẹ̀ẹ́ àti àgùtàn lọ́fẹ̀ẹ́ tí ó máa ń fẹ́ràn bẹ́ẹ̀ jẹ kiri kiri ilú.

Babaláwo tí ó dá Ifá yìí fún Bàbá-mọ̀le ni à ń pè ní Ji-ogiri-nú-fi-gbogbo-ara-jókòó. Bákan babaláwo náà ni ó dá orúkọ rẹ̀ lójú gan-an nínú Ifá-dídá nì wọ́n fi ń pè é ní Jingiri. Ẹsẹ Ifá yìí tún ṣe ìmúlẹ̀ ni ẹgẹ́ àwọn Ìmọ̀le tí ó máa ń rí gẹ́gẹ́ nǹkan náà pọ̀jù.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí òkun. Ẹsẹ náà pa ìtàn ìgbà tí gbogbo omi ni àwọn ó bá òkun ṣe mọ̀. Ní ojọ́ náà, àwọn babaláwo tí Olókun kọ kẹ́ sí ni à ń pè ní:

Ojú òkun ò ní í burú.
Kò mọ̀ kò kọ́ ilẹ̀ẹ́ ilẹ̀ẹ́ bíhọ̀nu;
Àwàlàwalà ọ̀gìrì-ọ̀run ò lọ lóòkó;
Ọ̀nà ìgbàlẹ̀ ò yà lọ́ níbi wọ̀
Fún àwọn ọmọ ẹlẹ́gbẹ́rì.

Ẹsẹ Ifá náà kò sọ bí wọ́n dá ẹbọ fún Olókun tàbí wọn ò dá ẹbọ fún un, ṣùgbọ́n ó dájú wí pé Olókun tí rúbọ bí ó ti ṣẹ̀gun gẹ́gẹ́ bí ẹsẹ Ifá náà ti sọ nínú rẹ̀.

Ìparí ẹsẹ Ifá náà wá dára gan Ifá. O fi ewé ọpẹ̀ṣẹ̀ṣẹ̀, ẹkọ ọlọ́sẹ̀ àti ìrùjẹ̀wọ̀ ọ̀pẹ̀ ṣe àpẹẹrẹ láti ìsàn àṣẹ rẹ̀ múlẹ̀. Bí ó bá ṣe wí pé a fẹ́ẹ́ jíire Ifá fún ọmọbìnrin yí ni, àwọn nǹkan tí a ó lo tọ́jú nǹ-un bí a tó tọ̀ Odù yí pẹ̀lú kíkí Odù náà bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. O dájú wí pé olórí kan ni ọmọbìnrin yí, ṣùgbọ́n àwọn ọmọ-ẹ̀hìn rẹ̀ ó fi lè kó o mọ̀. Ifá ń fún un ní ìdánilójú pé bí ó bá le rúbọ, tí ó sì lè ṣe ẹ̀tùtù, yóò padà sí ipò rẹ̀.

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àlàyé pàtàkì nípa òkun àti àwọn omi yòókù. Ifá ní dájúdájú, òkun ni ọba omi. Bí àwọn odò àti ọ̀sà yòókù tí lè tóbi

tó, wọn ò kọ̀ tì ìkun, lẹ́hìn tí wọn ó máa bá Olókun ṣọ̀tá, wọn ò lè tubi tó ókun. Èyí ni ìtumọ̀ àwọn ìlà mẹ́ta ìgbẹ̀hìn níbi tí Ifá gbé wí pé:

Àtoni, àtàgbénà,
Ẹ wá forí balẹ̀ fólókun,
Ólókun l'ayaba omi.

## Ẹsẹ Ẹkaàrùn

Ní ìbẹ̀rẹ̀, ẹsẹ Ifá yìí sọ̀rọ̀ nípa ẹyẹlé. Ifá kọ́kọ́ ṣàpẹ̀júwe bí ẹyẹlé ṣe ń fò lọ́gẹ̀ lọ́gẹ̀. Bí ẹyẹlé ṣe ń fò yí jọ ti aṣẹ̀wà àti afínjú ẹyẹ tàbí ẹyẹ tí kò lágbára tó bẹ́ẹ̀. Lẹ́hìn náà, Ifá ṣe àpèjúwe ìhùnhù ẹyẹlé. Ó ní ẹyẹlé ń ìhùnhù jọ̀ àdàbà.
Wàyí o, akọ ẹyẹ ni a kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún nítọ̀ tí ó ṣaráùn wí pé òun ò lóbìnrin. Ìparí ẹsẹ Ifá yìí fi hàn wí pé akọ ẹyẹ náà rúbọ, ó sì lóbìnrin. Ifá ń sọ nínú pé ẹni tí a dá Ifá yìí fún kò ní obìnrin. Bí ó bá fẹ́ rúbọ, yóò lóbìnrin.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ẹsẹ yìí ń tọ́ka sí àkókò kan tí Ọ̀rúnmìlà fẹ́ ń bẹ lààrin ìgbìrì ọ̀tá. Àwọn babaláwo t'ó dá Ifá fún Ọ̀rúnmìlà ní ọ̀jọ́ náà ni à ń pè ní:

Ọbẹ̀ mogbé àìkú;
Ọbẹ̀ mọ́nọ àìkú;
Àkìmọ̀ tí í mọ orí Olú
Kí í jẹ́ kí ó fọ́;
Àkàpata ẹkùn ọ̀wọ̀n.

Lẹ́hìn ìgbà tí Ọ̀rúnmìlà rúbọ tán, ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í sọ wí pé kí àwọn ọ̀tá òun ó sin lẹ́hìn òun. Ó ní kí wọn ó mọ̀ pàtàkì òun mọ̀ nítorí pé bí a pàtàkì orí, kò pé kí ó mọ̀ huruu; bí a pàtàkì adìẹ ògògìrò, kò pé k'ó má lu lyé. Ó ní kí wọn ó sìn lẹ́hìn òun nítorí pé bí a bá fẹ́ẹ́kọ̀ roko roko, b'ó bá yà, a sìn lẹ́hìn rẹ̀; bí akérèngbé bá fọ́, ẹni t'ó fi ń pọn omi a sìn lẹ́hìn rẹ̀.
Pàtàkì ohun tí Ifá ń wí nínú ẹsẹ Ifá yìí ni pé ọ̀tá pọ̀ fún ẹni tí a dá Ifá yìí fún. Olówarẹ̀ ń bẹ lààrin ọ̀gìrì ọ̀tá. Èéyàn pàtàkì bí ọba tàbí



ìjòyè ni eléyìí. Bí ó bá lè rúbọ, tí ó sì gbọ́ràn sí àwọn babaláwo lẹ́nu, yóò níí ìṣẹ́gun nítorí pé 'akìmọ̀ tí í mọ orí Olú kì í jẹ́ kí ó fọ́'.

## Ẹsẹ Èkeje

Ẹsẹ Ifá yìí ń sọ ìtàn Ọtún àti àwọn ọmọ rẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Ìtàn yí sọ wí pé aya Ọ̀rúnmìlà ni Ọtún. Ó kọ́kọ́ ṣe aláìrọ́mọ bí. Ṣùgbọ́n lẹ́hìn ìgbà tí àwọn babaláwo tí ó jẹ́ 'Àkùkọ t'ó kọ láàná, Ìkọ̀ ìrọ̀rọ̀ l'ó kọ' ti dífá fún un tán, ó sì bímọ. Ó bí àwọn ọmọbìnrin mẹ́ta. Nígbà tí àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta dàgbà tán, wọ́n fi bá ìyá wọn lọ sí ọjà Ìjàyè tí ìyá wọn ń ná. Èkíní ru ẹ̀fọ̀ yánrin, èkejì ru ẹ̀fọ̀ tẹ̀tẹ̀, ẹ̀kẹta ru ẹ̀fọ̀ ẹ̀wúro. Wọn ru ẹ̀fọ̀ wọ̀nyí lọ sí ọjà Ìjàyè, ṣùgbọ́n tí ilẹ̀ fi ṣú, wọn ò dé.
Nígbà tí ìyá wọn, ó rí wọn mọ́, l'ó bá bẹ̀rẹ̀ sí í wá wọn. Ó kọ́kọ́ pàdé àwọn ẹ̀rò ọjà lọ́nà. Ó béèrè àwọn ọmọ rẹ̀, wọ́n sì sọ fún un pé Ọ̀sìn, ọba Ìjàyè, gbe òkun sí àgbàlá, ó pàkan ṣe àbàlá, ó sì pàkan sí ìkùgún. L'ó bá ná ìdálẹ̀ mọ́lẹ̀, ni gbogbo àwọn ẹ̀rò ọjà bá kọ̀. L'ó bá tún gbéra, ó di ọjà Ìjàyè. Ó tún béèrè ọmọ rẹ̀, wọ́n sì fún un ní ìdáhùn kan náà. L'ó bá ná ìdálẹ̀ mọ́lẹ̀, ni àwọn ará ọjà bá kọ̀. Lẹ́hìn náà, ó lọ bá Ọ̀sìn, ọba Ìjàyè, ó bi í ní ìbéèrè kan náà, Ọ̀sìn sì fún un ní ìdáhùn pé òótọ́ ni òun pa àwọn ọmọ náà. Ni Ọtún bá ru Ọ̀sìn, ọba Ìjàyè. L'ó bá lọ bá ìyá Ọ̀sìn. Àwọn méjèèjì sì wọ ìjàkadì. Wọ́n jàjàjà. Nígbà tí kò sí ẹni tí ó lè ṣẹ́gun, ni wọ́n bá wọ̀rọ̀, wọ́n sì di agbo àti igbó.
L'ọ́nà kíní, ẹsẹ Ifá yìí ń fi ìgbàanìn abiyamọ hàn gbangba. Jẹ́ kí abiyamọ tí ọjà ọmọ tì pẹ́ rí délé, ṣùgbọ́n tí ó wá ṣàfí ọmọ l'ọ́jà alẹ́. Irú èèyàn bẹ́ẹ̀ kò ní í kọ̀ láti ṣe ohunkóhun. Àsìkò tí gbogbo ọmọ Yorùbá ń gbà ni pé kí ọmọ rere ó gbẹ̀hìn ẹni. Ifá ń kì ẹ̀kọ́ ẹni pé ẹnikan kọ̀ ìlà ẹ̀mí àwọn ọmọ tí abiyamọ bí lóglandé, wọn ò kọ̀ kí ẹ̀mí àwọn náà ó tán sí i.
L'ọ́nà kejì, ó dàbí ẹni pé Ọ̀sìn fi àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí bọ òrìṣà ni. Nítorí náà, ẹsẹ Ifá yìí ń tọ́ka sí àkókò tí wọn ń fi èèyàn bọ òrìṣà ní ilẹ̀ Yorùbá. Ṣùgbọ́n tí Ọtún sì ṣẹ́gun Ọ̀sìn fi hàn ni wí pé Ifá gbàgbọ́ ń sọ wí pé irú àṣà ìtàjẹ̀sílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ò dára.
L'ọ́nà kẹta, Ifá ń pìtàn ìlú Ìjàyè nínú ẹsẹ yìí. Ìlú tí a ń pè ní Ìjàyè yí ti dahoro báyìí. Ahoro ìlú náà ń bẹ ní agbede méjì Ìbàdàn àti Ọ̀yọ́ lónìí. Bóyá ìwà burúkú báyìí náà l'ó fà á tí ìlú náà fi di ahoro. Wíwọ̀ọ̀ tí Ọtún àti ìyá Ọ̀sìn wọ̀rọ̀, tí wọ́n sì di igbó àti ìgbà le jẹ́ ọ̀nà láti sọ fún wa wí pé ìlú náà di ahoro lẹ́hìn ìgbà tí

àwọn ọ̀tá Ìjàyè bá ìlú náà jà lójijì dúró̩gbé. Àwọn ọ̀tá pa èrò ọ̀jà, wọ́n ṣá àti ọba Ìjàyè run pátápátá. Ṣùgbọ́n wọn ò lè ru ilé Ìjàyè tí ó ṣe ìlú náà lọ. Ẹkẹ́ àwọn ọ̀tá Ìjàyè àti ti àwọn ará Ìjàyè náà ṣọ ilẹ̀ Ìjàyè di ahoro tó bẹ́ẹ̀ tí ìgbangan ilú tí Ìlú náà tí wà tí tẹ́tẹ́ fi jẹ́ igbó rabidun lónìí títuntagba àti ìjòkùn.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹjọ

Ọ̀rọ̀ nípa ayé ni ẹsẹ Ifá yìí ń sọ. Ẹsẹ Ifá náà dá lórí ọmọkan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Láàgbó Ọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Wọ́n sọ fún un pé yóò j'ayé ilé babaa rẹ̀. Ó rúbọ, ó sì jẹ ayé náà. Àwọn babaláwo tí ó dá Ifá náà fún un ni orúkọ Ọ̀gún àti Olùkì Ìtàn wò. Àwọ̀jé tí wọn ṣọ nípa Láàgbó Ọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀ ni ẹ̀ṣẹ̀ bí wọ́n ti wí.

Ohun tí Ifá ń sọ nípa fún ọmọlẹ́yìn yìí ni wí pé ayé ń rọ ọ́. Bí ó bá rúbọ, yóò tètè àwọn ọ̀tá rẹ̀, yóò sì jẹ ayé ilé babaa rẹ̀ nítorí pé orí ayé ni oloyè ara nàyí.

# 14 ÌRẸTẸ̀ MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Àwọn babaláwo mẹ́ji kan tí kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún Ìrẹtẹ̀ ni Ifá ń tọ́ka sí ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ yìí. Ọ̀kan nínú àwọn babaláwo náà jẹ́ ẹ̀àyàn tẹ́ẹ́rẹ́, ẹ̀keji sì jẹ́ ẹ̀àyàn gígùn, tí ó sì tún bá sùrù díẹ̀. Àwọn babaláwo náà l'ó dá Ifá yìí fún Ìrẹtẹ̀ ni Ìrẹtẹ̀ fi di olówó.

Ifá wá ń sọ nípa pé ẹnikẹ́ni tí a bá dá Ìrẹtẹ̀ Méjì fún ni láti di olówó dandan. Nítorí pé Ìrẹtẹ̀ tẹ méjì lẹ́ẹ̀kà, ó tẹ méjì ó la yẹbẹyẹbẹ. Nítorí náà ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ire ọlà fún ẹni tí a dá Ìrẹtẹ̀ Méjì fún.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí àti ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ pàtàkì. Ewé a máa gbó lára kùkùndùkù gẹ́gẹ́ bí Ifá ṣe wí nínú. Òótọ́ sì ni wí pé bí ẹ̀ẹ̀yàn bá ní ọ̀rọ̀ nígùn, yóò máa ru olùwarẹ̀ sókè pẹ̀lú ìgbéraga rẹ̀. Ifá wá ń ṣe àlàyé fún wa wí pé bí ẹ̀ẹ̀yàn tilẹ̀ ní ọ̀rọ̀ nígùn, ṣùgbọ́n tí olùwarẹ̀ ní ókè, ìrègún rẹ̀ ò ní í jẹ́.

Ẹsẹ Ifá yìí wá sọ ìtàn kan nípa Ọ̀rúnmìlà. Ó ṣe ìtàn ìgbà tí Ọ̀rúnmìlà fi ń lọ gbé Agùnbíọ̀ṣà níyàwó, tí ó fi ranṣẹ́ sí àwọn



babaláwo mẹ́ji pàtàkì kan: Akínkẹ̀búù, ọmọ l'ode Ìlọ̀bìn, àti Akínfálà, awo wọn òde Ìfàlà. Nígbà tí wọ́n dé, wọ́n wá bẹ̀rẹ̀ sí í bá Ọ̀rúnmìlà yọ̀, tí wọn sì ń kọrin Ifá.

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ire aya. Ifá ń sọ wí pé ẹni tí a dá Ifá yìí fún ń fẹ́ya láìpẹ́. Obìnrin náà ó jẹ́ ẹni tí ó lọ́wọ́, tí ó sì ṣe àníyàn rẹ̀ lénu. Kí onibèèrè náà ó máa múra síẹ̀ fún un.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Níhìn, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa òkè tí í ṣe ọmọ Olójà ọ̀run. Ifá ṣe àlàyé bí òkè ṣe ààfà ní òde-ọ̀run, kí ó tó wá sí òde ìsálayé; tí àwọn ọmọ rẹ̀ fi sọ wí pé b'ó bá dé'lé ayé tán, ẹsẹ̀ ọ̀nà ni kí ó máa tọ̀, nílẹ̀ sì ó ti bá ire tirẹ̀. Nígbà tí òkè dé'lé ayé tán, ó sì ṣe bẹ́ẹ̀. Ìdí nìyí tí òkè fi máa ń wà ní ẹsẹ̀ ọ̀nà.

Ifá ń ṣe àkíyèsí nínú nípa ìbí tí a ti máa ń rí òkè. Ọ̀nà kì í jìnnà púpọ̀ sí ẹsẹ̀kẹ̀ nítorí pé àwọn ọmọ aráyé a máa fẹ́ láti wo òkè ní ọ̀kánkán. Ìyẹ̀ tí òkè ní nípa bí ó máa wà ní, kí ó máa gùn ìn, kí ó sì máa sọ̀ kalẹ̀ yí ni ire tí òkè rí nípa ẹbọ tí ó rú lode-ọ̀run.

Ifá sọ ìpọ̀kọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ nípa òkè. Ohun ni Ifá pè ní 'ọmọ ọpá ò kú'. Nítorí náà, Ifá ń máa fi òkè ṣe àpẹẹrẹ ìsọ̀gun ọ̀tá. Òkè sì tún dúró fún àmì àìkú. Ifá wí nínú Ọ̀yẹ̀kú Méjì pé:

Ogún ọdún òní o,
Òkè ń bẹ láìkú gbọin gbọin.
Gbọin gbọin ni tòkè.
Òkè, òkè gbọin gbọin.
Ìgba ọdún òní o,
Òkè ń bẹ láìkú gbọin gbọin.
Gbọin gbọin ni tòkè.
Òkè, òkè gbọin gbọin.
Ìgbà gbogbo lòkè ń bẹ láìkú gbọin gbọin
Gbọin gbọin ni tòkè.
Òkè, òkè gbọin gbọin.

Ifá fẹ́ràn láti máa pe òkè ní ọlọmọ. A kò mọ ìdí náà tí Ifá fi ń pè é ní ọlọmọ. Òkè ni Ifá ń pè ní 'ọlọmọ àmàyékà'. Ohun náà ni wọ́n sì tún ń pè ní 'ọlọmọ ìyan ìyan gìdìgbà'.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Nínú ẹsẹ Ifá yìí, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa ibi kan tí ó pè ní òde Ọ̀tà. Ó wá ń sọ wí pé àti ìgbà tí a dá Ìrẹtẹ̀ Méjì fún wọn ní òde Ọ̀tà ni wọn tí rìre.

Ó dàbí ẹni wí pé Ifá fi àwọn obìnrin ṣe yẹ̀yẹ́ nínú ẹsẹ yìí díẹ̀. O jọ bí ẹni pé bí wọn ṣe ń 'tú ẹrù' ní ìkaakà ní òde Ọtẹ̀ yí gan-an ni oun tí ó sọ Ìlú náà di ìlú Ọtẹ̀. 'Ọ̀pọ̀n ará òde Ọtẹ̀' tí Ifá mẹ́nubà níhìín kò ní í ṣe lórí nǹkan obìnrin.

Nítorí náà, a lè sọ wí pé orígìrí̀gbì ìrònúrádà tí ó máa ń wá nínú ìlú ọ̀fàlè àti dọ̀kọ̀ọ̀kọ̀ ní Ifá fi ń ṣe yẹ̀yẹ́ níhìín. Ifá wá ń sọ wí pé kí ọ̀tẹ̀ tí ìrò lwà ìhùwà hàyìí máa ń dá sílẹ̀ ó lè kúrò, kí bí a bá rúbọ Ọ̀sà Méjì.

## Ẹsẹ Ẹ̀kaárùn

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ ọ̀rọ̀ nípa àwọn ìlú ayé àtijọ́. Àgbà jẹ́ ìlú àwọn Ògbómọ̀. Ilú yí wọ́ pọ̀ ní Ilé Ifẹ̀. Nítorí náà ni a fi ń ki àwọn ọmọ Olúfẹ̀ ní 'ọmọ kẹ̀ẹ̀ lágbàá dúró'. Ìpèsè jẹ́ ìlú Ifá. Òun náà ni à ń pè ní àràn. Ìlú pàtàkì l'ó jẹ́ fún àwọn babaláwo. Ọ̀pọ̀ sì ni ẹsẹ Ifá tí ó tọ́ka sí èyí nítí tí Ifá gbé sọ wí pé:

> Wọ́n sìgbó sàràn,
> Ó mú r'ìnùn rẹ̀ jáde.

Ìlú àgbà àti ìlú ìpèsè yí náà ni Ifá ń júwe nígbà tí ó wí pé:

> Àgbà bori pẹ̀rẹ̀,
> Ìpèsè abọgbàrí jìnnjìnnìkunjìn.

Ifá tún sọ̀rọ̀ ìlú tí a ń pè ní ogidan. Ìlú yí náà jẹ́ ìlú ayé àtijọ́.

Ẹsẹ Ifá yìí wá dá lé'ri ọ̀rọ̀. Ifá ní bí ẹlẹ́yìí ò bá kú, yóò là, yóò sì lóruó lọ́wọ́, yóò sì tún bímọ pẹ̀lú. Lẹ́hìn ìgbà tí ó bá rí gbogbo nǹkan tí a fẹ́ wọ̀nyí tán, kí ó máa jó, kí ó máa yọ̀ l'ọ́ kú. Èyí ni wí pé kí àgbà ó máa ṣubú lágbà, kí ogidan ó máa ṣubú logidan, kí ìpèsè ó máa ṣubú lìpèsè. ẹ̀yẹ̀ bí orúkọ àwọn olúwo tí ó kọ̀kọ̀ dá Ifá yìí fún Òkù Ìlú tí a ń pè ní Òrèrè.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí àwọn ará òde Ẹ̀gbá tí wọ́n sọ fún pé kí wọn ó rúbọ nítorí 'ọmọ tí yóò jogbó jatọ̀'. Àwọn ará òde Ẹ̀gbá rúbọ, wọn sì bí ọmọ náà tí ó jogbó jatọ̀. Ohun tí Ifá ń wí níhìín dá lórí ọ̀rọ̀ ogbó. Ọmọbìnrin yí bí ọmọ kan (tàbí yóò bí ọmọ kan) tí ó pẹ́ láyé. Kí ó rúbọ ogbó fún ọmọ náà nítí tí a gbé dá Ìrẹtẹ̀ Méjì.



Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí bá tí ó ṣẹ̀ sílẹ̀ láti ọjọ́-ọjọ́un. Ifá tún sọ̀rọ̀ nípa eruku ojúde gbangba nítí tí àwọn ọmọdé ti máa ń ṣiré. Ifá tún ṣe àkíyèsí nípa àràn tí akún máa ń wá jáde láti inú ẹ̀ẹ̀ ri bí ó ṣe máa ń rọ̀ nítorí pé inú omi ló ti wá á jáde. Láti ibi ọ̀rọ̀ ìrán akún yí ni Ifá ti sé mọ́ ọ̀rọ̀ nípa ìdẹ̀ àti ẹyẹlẹ́. Ó ní 'ìdẹ̀ fi iyẹ̀ sọ̀rọ̀; ẹyẹlẹ́ fi oògun sọ̀rọ̀'.

Ifá tún wá sọ̀rọ̀ nípa àwọn ará òde Ẹ̀gbá. Ó sọ nípa bí wọn ṣe fẹ́ràn láti máa bọ igi inú igbó bí igi ìrókò ní òde Ẹ̀gbá. Ifá tún sọ̀rọ̀ nípa Orò tí àwọn ará òde Ẹ̀gbá máa ń bọ. Ó ní ìgbà ìgbó ni wọn fi máa ń ṣe nílẹ̀.

Ọ̀rọ̀ nípa ìségun ni ẹsẹ Ifá yìí wáá sọ ní ìparí. Ifá ń ṣe ìlérí fún ẹni tí ó dá Ìrẹtẹ̀ Méjì pé bí ó bá le rúbọ, yóò ní ìségun. Kí ọ̀kànwarẹ̀ ó lọ bọ Ìrókò àti Orò fún ìségun ọ̀tá. Bí ẹlẹ́yìí bá wá pẹ̀gun ọ̀tá tán wayí o, yóò wáá bí ọmọ aláràbàríkà kan, tí yóò gbórò púpọ̀ láyé.

## Ẹsẹ Ẹ̀keje

Ìtàn ní ẹsẹ Ifá yìí ń pa nípa Ọ̀rúnmìlà. Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà ń lọ sí Ifẹ̀ láti lọ dá nǹkọ́, àwọn ọ̀tá sọ wí pé kò ní í rí ẹ̀yìn bá a dé nílẹ̀. Wọ́n ní ojú ni ó gbóó Ọ̀rúnmìlà; wọn ní àkọ́kọ ni ó ti bím; ìgbà ni ó bím ìn. Ṣùgbọ́n lẹ́hìn ìgbà tí Ọ̀rúnmìlà ti rúbọ tán, ó gbéra, ó lọ sí Ifẹ̀. Ibẹ̀ sì gbà á. Ó di ẹlẹ́yìn nílẹ̀.

Ọ̀rọ̀ nípa nínú ọ̀pọ̀ ẹ̀yìn lẹ́hìn ni Ọ̀rúnmìlà ń sọ níhìín. Ẹni tí ó dá Ifá yìí fún jẹ́ olórí kan, tí ó lọ sí ibikan. Kí ó rúbọ, kí ó lè bọ̀ ní àlàáfíà nílẹ̀.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejọ

Ọ̀rọ̀ nípa ikú ni ẹsẹ Ifá yìí dá lé lórí. Ifá ní òun rí ikú nítí tí a gbé dá Ìrẹtẹ̀ Méjì. Kí àwọn ará ìlú ibi tí ẹni tí ó dá Ifá fún wà ó má ba ìlú ní odidi ọdún mẹ́ta, oṣù mẹ́ta àti ọjọ́ mẹ́ta. Bí wọn bá lè ṣe bẹ́ẹ̀, wọn ó ṣẹ́gun àwọn ajogun.

Ẹsẹ Ifá yìí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àkíyèsí nípa ìdìgbà àti ọdún bí wọn ṣe máa ń fò, tí wọn ó ta kónkóró lórí igi ibi àti igi ẹmí, tí wọn ń máa ń fi inú na ara wọn. Ẹni tí a dá Ifá náà fún ni à ń pè ní Olókọ̀tún, Ìrẹ̀-dede. Ó jẹ́ ọmọ ìlú Ọ̀tún. Wọn dá Ifá náà fún un ní ọjọ́ tí ó ń lọ pe ìgèdè sí ikú. Ifá ń sọ wí pé bí Olókọ̀tún ṣe ní ìségun ní ìlú Ọ̀tún ni ẹlẹ́yìí náà ó ṣe ní ìségun bí ó bá lèè rúbọ.

# 15 ÒSÉ MÉJÌ

## Ẹsẹ Èkíní

Ọlọ́fin ni wọn kọ́kọ́ dá ẹsẹ Ifá yìí fún. Àwọn babaláwo t'ó dá Ifá náà fún Ọlọ́fin ni ó ń pè ni àwọn 'Agada ò tàsè m'ori ẹni ó rọ̀wọ mọ́'. Ohun tí Ọlọ́fin dá Ifá nítorí rẹ̀ ni nípa ìṣẹ́gun ọ̀tá. Lẹ́hìn ìgbà tí Ọlọ́fin rúbọ tán, ó sì ṣẹ́gun. Èyí l'ó mú kí Ifá ó sọ nǹkan pé:

> Kíni ẹbọ ńlí gbe ni,
> Àìní kí í gbèéyàn.

A rí ìpọ́nrìn tí ó fi hàn wá wí pé ìjà tàbí ogun gidi ni àwọn ọ̀tá Ọlọ́fin ń bá a jà kí ó tó lọ dá Ifá yìí. Ohun tí ó tọ́ka sí ìjà nínú ẹsẹ yìí ni:

> Kí á f'igi rogi,
> Kí á lé gb'ohùn igi.
> Kí á fi ọ̀pẹ́ na ọ̀pẹ́,
> Kí á lé bọ̀ gb'ohùn ọ̀pẹ́.

## Ẹsẹ Èkejì

Ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ó sọ̀rọ̀ nípa ìyì àti agbára tí babaláwo ní. Ẹnìkan kò gbọ́dọ̀ fi ibinú bá wọn gbólé, bẹ́ẹ̀ ni a kò sì gbọ́dọ̀ fi ibinú lé wọn bọ́ sódè, kí olúwarẹ̀ ó má baà tọ̀ bọ gbọ̀n ọ̀ràn.

Ẹni tí wọn kọ́kọ́ dá Ifá yìí fún ni Lápàdé, ọmọ Ọ̀ṣùrú ẹ̀wà. Ìlí Lápàdé tí ó f'ògbọ́n inú yanwó ni ìkà tí ń fi ọgbọ́n inú lé e kiri. Ẹsẹ Ifá náà wá sọ ní àpẹrẹ wí pé ó yẹ kí ìkà ó le máa bẹ̀rù awo bí ó bá wọ inú ilé kan nítorí pé bí inú bá jó kíkiko ilé a máa bẹ̀rù àjà. Nítorí náà ni inú kì í fi í jó àjà tán pátápátá nígbà tí ilé bá jó.

Ọ̀rọ̀ inú ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ìkà. Ifá sọ wí pé ẹnikẹ́ni tí ó ṣìṣẹ́ owó pẹ̀lú agbára àti ọgbọ́n inú. Kí olúwarẹ̀ ó ṣọ́ra o, kí ó má lọ jẹ pé ìgbẹ̀sẹ̀ ìkà náà ni ìkà ó tí pa á.

## Ẹsẹ Ẹkẹta

Nǹkan mẹ́jì pàtàkì ni Ifá ń sọ nìbí. Lọ́nà kíní, Ifá ń sọ wí pé ẹni tí ara rẹ̀ bá le, kí í ṣe wí pé ara rẹ̀ lásán ní ó máa fi ò fún. Ṣùgbọ́n bí èèyàn bá tí dí ọ̀jẹ̀kúnrin, ó di pé kí òun nǹkan ó máa



dà ara lásán náà jẹ. Kò sí ẹni tí ó le gba lásán náà fún un bẹ́ẹ̀ ni òun náà kò lè rán ẹni kan kan lọ́wọ́ mọ́.

Ifá wáá tún sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀rẹ̀ jẹ́jẹ́ nínú ẹsẹ yìí. Ó ní ẹ̀rẹ̀ ò lóri ìgbẹ̀rẹ̀ lẹ̀, orí rere ni ẹ̀rẹ̀. Ẹ̀nikẹ́ni tí ó bá sì jẹ ohun tí ó ń pè ni ẹ̀rẹ̀ yì, olúwarẹ̀ náà ni kíni jẹ olórí rere. Ohun tí Ifá ń sọ fún wa nìbí ni wí pé ẹ̀rẹ̀ tí a máa ń jẹ n'ílẹ̀ ayé ni orígìnígìì ọ̀nà, àwọn irúnmọlẹ̀ l'ó máa ń fún ni jẹ nítorí pé ẹrú Ọ̀rúnmìlà ni à ń pè ní ẹ̀rẹ̀. Ṣùgbọ́n ẹnìkan rere ni ẹ̀rẹ̀ nítorí pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ ẹrú, kì í fi orí rẹ̀ nǹkan kan. Nítorí náà olórí ire ni ẹ̀rẹ̀, olórí ire náà sì ni ẹni tí Ọ̀rúnmìlà bá fi ta lọ́rẹ.

## Ẹsẹ Ẹkẹrin

Ọ̀rọ̀ nípa ọ̀rẹ́ ni Ifá ń sọ nìbí. Ifá ní a kò gbọ́dọ̀ pèkìrì ọ̀rẹ́ nítorí pé ọ̀rẹ́ ni ọ̀rẹ́, a kò sì gbọ́dọ̀ dalẹ̀ ọ̀rẹ́. Ifá ń ṣe àlàyé pé a kò gbọ́dọ̀ dalẹ̀ ọ̀rẹ́ ìmúlẹ̀. Ifá sọ wí pé inú ọ̀rẹ́ mẹ́jì kò lè rí bákan náà. Èyí l'ó fà á tí ọ̀rẹ́ mẹ́jì fi máa ń jà. Ṣùgbọ́n nílẹ̀mílẹ̀, ẹni tí a bá pè ní ọ̀rẹ́, a kò gbọ́dọ̀ pèkìrì rẹ̀.

Ifá tún wá ń tọ́ka sí ọ̀rẹ́ ìmúlẹ̀ tí ń bẹ láàrin Ọ̀ṣẹ̀ẹ́rẹ̀ àti irúnmọlẹ̀ yòókù nígbà tí wọn ń lọ láti òde-ọ̀run wá sí ìl'-ayé. Ìdí níyẹ́ tí ó fi jẹ́ wí pé àwọn òrìṣà kì í da ara wọn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn a máa bá ara wọn jà lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan.

## Ẹsẹ Ẹkarùn

L'ọ́nà kíní, ẹsẹ Ifá yìí ba aláìrúbọ wí. Ó fi hàn pé ọlẹ tí ó dẹ̀ ìgbẹ́ òru, tí wọn ní kó rúbọ tí kò rú, ṣe ìpọ́nrìn. Nítorí pé ọlẹ ò rúbọ, ó kiri kiri inú igbó fún nǹkan bí odidi ọdún kan, ṣùgbọ́n kò rí ẹran pa. Àfi nígbà tí ó wá lọ rú ẹbọ tí wọn ní k'ó rú, l'ó wá bẹ̀rẹ̀ sí í rí ẹran pa. Ó le ìgbín kan, ó le ahun kan, ó sì fi yíà pa àgbọ̀nrín. Nítorí náà, Ifá ń sọ fún wa wí pé 'ìrìn ẹbọ ni í gbe ni, àìní kì í gbèéyàn'.

L'ọ́nà kejì, ẹsẹ Ifá yìí ń sọ fún wa wí pé ẹni tí ó bá da owó alàjíjì ni ó tẹ ilẹ̀ tútù. Lẹ́hìn ìgbà tí ọlẹ fi ìgbín àti ahun rúbọ tán ni òun náà tó rí ìgbín àti ahun he. Lẹ́hìn náà l'ó tó wá pa àgbọ̀nrín.

## Ẹsẹ Ẹkẹfà

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí ìṣẹ́gun ọ̀tá. Àwọn ọ̀tá ń yọ ẹni tí a dá Ifá yìí fún lẹ́nu. Bí ó bá le rúbọ, yóò lékè gẹ̀gẹ̀ bí Ẹlà ṣe lékè orí, tí akẹ̀rẹ̀ lékè Ẹ̀lù, tí òtútù sì í lékè ilẹ̀.

Ayé kìíní ẹsẹ Ifá yìí kọ́kọ́ dárúkọ àwọn babaláwo tí ó dá Ifá yìí fún ọ̀kọ̀mọ̀ kan. Bóyá ìdí tí wọn fi dá Ifá náà fún ọ̀kọ̀mọ̀ kàn ni wí pé àwọn ọtá fẹ́ gbé ọmọ kan náà mì. Wọ́n ní fún ọ̀kọ̀mọ̀ kàn pé kó rúbọ. Ẹsẹ Ifá yìí kò ṣe àlàyé síwájú bí ó ṣe ẹbọ náà tàbí kò rú u. Ṣùgbọ́n a mọ̀ wí pé bí ó bá rúbọ, yóò ṣẹ́gun.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹta

Ẹsẹ Ifá yìí ń pàtàn gẹ́gẹ́ bí ẹyẹ olongo ṣe di oníyì láàrin àwọn ẹyẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ó kéré púpọ̀. Ifá sọ wí pé ní àkọ́kọ́, ògòngò ni olongo kọ́ fẹ́ máa bá rìn nítorí pé ó rò pé òun náà ó di ẹyẹ títóbi bí òun bá ṣe bẹ́ẹ̀. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó fi ọ̀rọ̀ náà lọ àwọn awo rẹ̀, wọ́n sọ wí pé kò kò wọ̀ kí olongo ó máa bá ògòngò rìn. Wọ́n ní:

> Ọ̀ṣọ̀ṣọ̀ rẹ̀ kò gbọdọ̀ tẹlẹ̀ bí ògòngò,
> Bí ó bá wí pé òun ó rìn bí ògòngò,
> Ìbẹ̀ ní ẹsẹ̀ rẹ̀ ó ó ṣẹ́.
> Kí ẹni yánwọ́nrín mú ṣe bí
> Eni tìkàànníṣẹ́ rìn,

Nígbà tí olongo gbọ́ báyìí, l'ó bá bi àwọn awo rẹ̀ wí pé bí òun kò bá tilẹ̀ le tóbi sí i mọ́, kín ni òun lè ṣe tí òun fi lè níyì. Wọ́n wá gbà á níyànjú pé k'ó rúbọ iyì. Wọ́n ní k'ó fi aṣọ funfun bàlàú kan àti aṣọ ẹtù kan rúbọ pẹ̀lú owó àdáálú kan. Nígbà tí Èṣù gba ẹbọ náà tán, ó wá dá ìrù aṣọ tí olongo fi rúbọ náà, ó ní kí olongo ó máa wọ̀ ọ́. Olongo sì ṣe bẹ́ẹ̀. L'ó bá di oníyì láàrin ẹyẹ. Ìdí nìyí tí àwọn ẹyẹ oko fi máa ń pé bá olongo, tí wọn ó sì máa ṣe é nìbìkíbi tí ó bá wà.

Olùun tí Ifá ń wí nihìin ni wí pé kí á tó máa bá èèyàn rìn, kí á rí i wí pé irìn ẹsẹ̀ rẹ̀, ìrìn àti ìhùwàsí rẹ̀ jọ tiwa. Bí a bá fi tipátipá bá ẹni tí ó jù wá lọ rìn, ìjàǹbá lè ti ibẹ̀ wá. Ifá tún ń sọ wí pé aṣọ àlà kọ́ ni èèyàn òkù. Bí èèyàn kò tilẹ̀ tóbi, tí kò lówó, tí kò sì ní agbára bí àwọn ọmọ oníyè yòókù, bí ó bá ti níyì àbùṣé bùṣe. Nítorí náà ẹbọ bí Olórun ó ṣe dá aṣọ iyì bá wa ni à bá máa rú dípò bí a ó ṣe tóbi tàbí bí a ó ṣe di alágbára.

## Ẹsẹ Ẹ̀kẹrin

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí pàtàkì nípa àwọn ẹranko inú igbó mẹ́jì, ẹtu àti òkè. Ẹtu, ọ̀kẹ́rẹ́, ẹlẹ́ṣẹ̀ ọwọ́, jẹ ẹranko kékeré kan báyìí tí ó fẹ́rẹ̀ tó ewúrẹ́. Ó jẹ́ ẹranko tí ó ní ìfura púpọ̀, ọwọ́ rẹ̀ sì yá nílẹ̀ bí ó bá ń sáré. Òkè jẹ́ ẹranko kan tí ó ní ipé lára. Bí àwọn ọdẹ tàbí



ajá ọdẹ bá tí ó bá e lọ, yóò kan orí mọ́lẹ̀, yóò wá balaakáká, yóò sì bẹ̀rẹ̀ sí í ta ipé ara rẹ̀ mọ́ àwọn ọ̀tá.

Olùun tí Ifá wá ń sọ nihìin yìí ni pé àìgbọràn òkè àti pípá tí ó pá ẹbọ rù l'ó fà á tí ọwọ́ àwọn ọ̀tá fi máa ń tẹ̀ ẹ́. Òótọ́ kò rú ẹbọ tí àwọn awo rẹ̀ dá fún un tán nítorí pé ó ti gbẹ́kẹ̀lé ipé rẹ̀ ju b'ó ti yẹ lọ. Ṣùgbọ́n ẹtu tí kò tilẹ̀ ní agbára kankan, tí kò sì ní ipé lára, ó bọ́ lọ́wọ́ àwọn ọ̀tá nítorí pé ó ní ìfura. Ìmọ̀ràn èyí ni pé ẹni tí ó bá gbẹ́kẹ̀lé ara rẹ̀ ju bí ó ti yẹ lọ kò ní í pẹ́ tí yóò fi bọ́ s'ọ́wọ́ àwọn ọ̀tá. A kò gbọdọ̀ gbẹ́kẹ̀lé ara ẹni débi kí a máa rúù ẹbọ tàbí kí á má ṣètùtù gẹ́gẹ́ bí àwọn babaláwo bá ṣe kà fún ni lẹ́hìn Ifá dídá.

# 16 Ọ̀RÀNGÚN MÉJÌ

## Ẹsẹ Ẹ̀kíní

Ọ̀rọ̀ nípa ogun ni ẹsẹ Ifá yìí fi bẹ̀rẹ̀. Ó ní jíjàlù ogun, àti jíjàlù ogun, kò sí èyí t'ó dára nínú. Ó tún wá sọ pé àjàlù ogun ni í jẹ́ kí èèyàn ó mọ ọ̀kùnrin nígbà tí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ogún le sọ ọmọkùnrin mílíràn di ẹrú, tí a ó fi ààbà dè lẹ́ẹ̀rin mọ́lẹ̀ pinpinpin.

Ẹsẹ Ifá yìí tún wá sọ̀rọ̀ nípa Olúgbà èyí tí a gbọ́ pé ó jẹ́ ọ̀dọ̀ ogun ní ayé àtijọ́. Ifá ní ọ̀nà tí olúgbòjúgbòjú fi ń ṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀ ni pé ó máa fi agara dá wọn l'ójú-ogun. Ifá wá sọ wí pé agara jẹ́ ọmọ Olódùmarè. Agara kì í bá èèyàn jà tí ó fi ń dà ni. Ifá a bá sọ wí pé agara dá Lámọrín, kí í ṣe ọ̀rọ̀ pé nǹkankan l'ó bá olúwarẹ̀ jà, bí kò ṣe wí pé alárà tán olúwarẹ̀ lòhì ọ̀kan ara rẹ̀ wá.

## Ẹsẹ Ẹ̀kejì

Ifá ń sọ ìtàn Àmúrè nihìin. Ó sọ wí pé ọmọ bíbí inú Ọ̀rúnmìlà ni Àmúrè. Àmúrè tí a ń wí yìí wá jẹ́ ẹni kòkúrú, nítorí náà ni Ifá fi pé é ní 'Àmúrè ó dìgbò'. Ifá wá bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ̀bẹ̀ fún Àmúrè, ọmọ rẹ̀, ẹni tí a pè orúkọ rẹ̀ kúrú sí Àmú, wí pé kí wọn ó ma'bí rere, kí wọn ó fi wọ̀ sí; nítorí pé kò níkì, bẹ́ẹ̀ ni kò lọ́rà.

Nibi tí ẹsẹ Ifá yìí sì gbé ya àyàbà lọ s'ìbi Ẹsẹ̀-kan-ọlà, olùun tí ó sọ nibẹ̀ ni pé bí a bá tí dá Odù tí a ń pè ní Ẹsẹ̀-kan-ọlà tán, kò tún sí pé kí a tẹ̀ ẹ́ sí ojú ọpọ́n, kí á máa kì í lọ tèti nítorí pé ìre kò ní í pẹ́ dé fún ẹni tí a dá Ẹsẹ̀-kan-ọlà fún. Odù Ìdìngbódù ni à ń pè ní Ẹsẹ̀-kan-ọlà.

Ní ìkẹ́rẹ̀, ẹsẹ̀ Ifá yìí ń sọ̀rọ̀ nípa bí ó ṣe yẹ kí nǹkan ó máa lọ ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lẹ̀: kí ẹsẹ̀ kan ó ṣaájú, kí èkejì ó tẹ̀lé e; kí baba ó ṣíwájú, kí ọmọ rẹ̀ ó tẹ̀lé e. Irú ètò bẹ́ẹ̀ l'ó ń jẹ́ kí ayé ó máa lọ ní ètò. Ohun tí Ọ̀rúnmìlà ń sọ nìhín ni pé kí ọmọ aráyé ó tẹ̀wọ́ gba Àmúwá ọmọ Òun, kí ó lè baà ráyè ṣe iṣẹ́ òun baba rẹ̀.

## Ẹsẹ̀ Ìkẹta

Ọ̀rọ̀ nípa ẹgbinrín ọ̀tẹ̀ ni ẹsẹ̀ Ifá yìí ń sọ. Ìkẹ́rẹ̀ ẹsẹ̀ Ifá yìí ń sọ wí pé ẹgbinrín ni ọ̀tẹ̀, bí a ti ń pa ọ̀kan ni ọ̀kan ń rú. Ohun tí Ifá ń sọ níyẹ́ nígbà tí ó wí pé bí a ṣe fi arò pakè sú, ìtàkè tún ń jẹ mú; bí a ṣe fi ìtọ̀ pajà rú, ìṣẹ́ṣẹ̀ tún ń jẹ ẹ̀yin.

Nígbà tí irú ọ̀tẹ̀ náà wá kọ̀ tí ó kò mọ̀ l'ó wá di wí pé ó ń rán ìgbá, ó ń ran ìsero, ó ń ran àwọn babaláwo pẹ̀lú; nítorí pé a ń rí awo ìdí. Àwọn awo ìdí yí ni Ifá pè ní ọ̀kà tí ó dìfá, paramọ̀lẹ̀ tí ó dìbò àti mọ́jàlmọ̀jàlá tí ń ṣe àrólà ẹbọ.

Ifá ń sọ nìhín pé ẹlẹ́yìí ń bẹ láàrin ìgbìrì ọ̀tà. Láàrin ejò olóró l'ó ń gbé pẹ̀lú. Kí ó rúbọ kí ó lè baà ní ìṣẹ́gun gẹ́gẹ́ bí Ọ̀fún ṣe ṣẹ́gun àwọn ọ̀tà ní ayé ìjẹ́lọ̀ nígbà tí a kọ́kọ́ dá Ifá yìí.

## Ẹsẹ̀ Ìkẹrin

Ifá ni àṣà rẹ̀ ìjà àwọn Ẹlẹyẹ nítorí tí a gbé dá Ọ̀rànmíyàn Mọ́jì. Bí wá alọ́wàn kan sí ń bẹ ní ìgangan ibẹ̀, kí ẹlẹ́yìí ó mọ̀ pé ìjà àwọn Ẹlẹyẹ ni o. Ohun tí ó sì fa ìjà àwọn ìyámi fún ẹlẹ́yìí ni pé olúwarẹ̀ fi nǹkan jíjẹ kan fi àwọn àgbà lọ́jú. Kí olúwarẹ̀ ó lọ fún àwọn ìyámi ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkàrà, kí ó lè baà gbádùn. Bọ́yá nǹkan l'ó sì ń dẹ́rùbà ẹlẹ́yìí ní alẹ́ tàbí lójú-oorun, kí ó mọ̀ dájú pé ìjà àwọn Ẹlẹyẹ ni o. Kí ó rúbọ kí ó lè baà ní ìṣẹ́gun.

Ìkẹ́rẹ̀ ẹsẹ̀ Ifá yìí sọ̀rọ̀ nípa àwọn ẹyẹ aláàmì mẹ́jì: àpà àti ọ̀ghìngbìn. A gbà gbọ́ wí pé bí àwọn ẹyẹ méjì yí bá ti ń ké kìkankìkan, a jẹ́ wí pé àìsàn ń ṣe ẹnìkan nínú ilé ni. Kí wọn ó kìyè sí olúwarẹ̀, kí ó má lọ jẹ wí pé àìsàn ìkú rẹ̀ l'ó ṣe. Irú ẹyẹ aláàmì mìíràn tí kìkí rẹ̀ máa ń bu ní ìgbà ni ẹyẹ tí a ń pè ní àwòrè. Bí ẹyẹ náà bá ké, tí kò sì wá a pẹ̀lú 'ọ̀rọ̀ ṣíṣẹ́, ṣíṣẹ́', a jẹ wí pé àìsàn ń ṣe ẹnìkan nítòsí tí ó sì jẹ́ wí pé àìsàn náà ń lo lọ́wọ́-lọ́wọ́ ní àkókò náà.

## Ẹsẹ̀ Ìkarùn

Ẹsẹ̀ Ifá yìí dá lórí Odù tí a ń pè ní Ògúǹdá ìkọ́kọ́ tí àwọn babaláwo ń lọ. Ògúǹdá yí wá ní'bi ìpanọ̀ kan nítorí tí àwọn babaláwo gbé máa ń lọ yọ̀ ọ wò. Ọ̀kọ̀ọ̀kan ni àwọn babaláwo máa ń lọ Ògúǹdá yí. Wọ́n sì gbà gbọ́ wí pé bí àwọn bá ti fojú ba Ògúǹdá náà tán, ìrẹ̀ dé. Ọ̀kan nínú orin tí wọn máa ń kọ nígbà tí wọn bá ń lọ wo Odù ni:

A fojú bOdù,
A rìre ó.
A fojú bOdù,
A rìre.
Àwá mọ̀ mọ̀ wáá fojú bOdù,
A ó kú mọ́.
A fojú bOdù,
A rìre.

Kò sì ẹni tí ó gbọ́dọ̀ fi ojú kan òrìṣà tí a ń pè ní Odù yí bí àwọn babaláwo olódù. Babaláwo tí kò ì tí ì jẹ̀ kò lè tíì jẹ̀ wọ́ ilé ti Odù kò gbọ́dọ̀ fi ojú kan Ògúǹdá ìkọ́kọ́ yí. Bí a bá sì fojú ba Ògúǹdá yí tán, a kò gbọ́dọ̀ sọ ohun tí a rí fún ẹlòmíràn tí kì í ṣe babaláwo olódù. Nítorí oríkì òrìṣà yí ni àwọn babaláwo tí ń mú oríkì bí Odùrẹ́yọ̀, Odùwàlé àti Odùbọ̀nmí.

Wàyí o, Ifá ń sọ àmọ̀ràn fún ẹni'bìrí yí pé kí ó máa múra sílẹ̀ fún àlejò pàtàkì kan lálẹ́. Àlùbàríkà ni àlejò náà. Kí ó jù kí àlejò náà, kí ó sì yọ̀ kí i, nítorí pé ire ń bẹ lọ́wọ́ àlejò náà.

## Ẹsẹ̀ Ìkẹfà

Ní ìkẹ́rẹ̀, nítorí oríkì àwọn olúwo t'ó kọ́kọ́ dá Ifá yìí, Ifá ń sọ̀rọ̀ nípa ilẹ̀ tí ó wà láàrin àwọn ọdẹ, àgbẹ̀ àti babaláwo, bí wọn bá ti fojúkan ara wọn. Wọn a kí ara wọn tayọ̀tayọ̀, wọn a jọ kíra wọn, wọn a sì dìbò iyèkan. Ohun tí Ifá ń sọ nìhín ni wí pé ó yẹ kí ìrẹ́pọ̀ àti ilẹ̀ ó wà láàrin àwọn ẹ̀yin t'ó bá jọ ń ṣiṣẹ́ kan náà tàbí ó jẹ́ ọmọ ìyá ẹgbẹ́ tàbí awo kan náà.

Ọ̀rọ̀ nípa ẹbọ rírú àti ìmúyàn ni ẹsẹ̀ Ifá yìí dá lé lórí. O ní nígbà tí orí ń sunkún àti Ìkòkò, l'ó bá rúbọ. Nígbà t'ó dé'lé ayé, orí sì Ìkòkò, Ọ̀rọ̀ náà ń sunkún àti lo ẹ̀jìgbàrà ìlẹ̀kẹ̀, bóbẹ́ẹ̀ sì ń sunkún mọ́nàmọ́nà, àyọ̀ ọba t'ó kúnà yanranyanran. Ohun tí Ifá ń wí nìhín ni pé bí ẹ̀yàn bá yan orí rere lórí ọ̀run wá, tí olúwarẹ̀ sì ń rúbọ bí ó ti tọ̀ àti bí ó ti yẹ, dandan ni kí olúwarẹ̀ ó di ọlọ́rọ̀.

Ìpari ẹsẹ̀ Ifá yìí jẹ́ àkíyèsí pàtàkì tí Ifá ṣe fún àwọn awo rẹ̀. O ní òun ò ní í jẹ́ kí àwọn awo òun ó fọ̀ṣẹ̀ hanlẹ̀, tí kí wọn ó máa gun orí ẹṣin. Ẹnikẹ́ni tí a bá tilẹ̀ dá Ọ̀rànmíyàn Mọ́jì f'ún, bí olúwarẹ̀ ṣe awo tàbí ọ̀gbẹ̀rì, dandan ni kí ó ṣe orí rere, bí ó bá le rúbọ nítorí pé awo rere ni Ọ̀rànmíyàn ń ṣe ọlọ́fẹ̀.

### Ẹsẹ Èkejè

Ẹsẹ Ifá yìí dá lóri ọ̀bùn. Ifá ba ẹnu àtẹ̀ lu ìwà ọ̀bùn nínú ẹsẹ yìí. Ó ní ẹni tí ó bá jẹ́ afínjú, ṣùgbọ́n tí ó wá lọ yan ọ̀bùn láié, a jẹ́ wí pé ó fi nǹjú kàrùn nìyẹn. Ifá wá tọ́ka sí hùwà ara mẹ́jì tí a ti lè dá ọ̀bùn mọ̀. Èkíní ni ìdákomú owó, èkejì ni aṣọ. Ẹnikẹ́ni tí kò bá tọ́jú ibi mẹ́jẹ̀jì yí, kí á mọ̀ dájú pé ọ̀bùn ni olúwarẹ̀.

Ifá wá tún tọ́ka sí ìtàn kan nípa bí obìnrin Àgbọnnìrègùn ṣe máa nítorí pé ọ̀bọ rẹ̀ bà a wí lóri ọ̀rọ̀ ìmọ́. Ifá ní kò yẹ kí a ní ọ̀bùn lóbìnrin. Ẹni tí ó bá sì ní ọ̀bùn lóbìnrin kò gbọdọ̀ jẹ irú mọ́ nítorí pé irú ni a lè fi òéri ara ọ̀bùn ìyàwó rẹ̀ wé. Bí ó bá sì le rí irú jẹ l'ára ìyàwó rẹ̀, èwo ni tí kí ó tún máa kówó rárá.

### Ẹsẹ Èkejo

Ẹsẹ Ifá yìí dá lórí Olókun, ẹni tí oríkì rẹ̀ ń jẹ́:

Olókun, sẹ̀ní adé,
Ajíláòkí, ọmọ ọba lábàlabà,
Ifá iglá ẹpo.

A kò ṣọ kíí tí Olókun fi dífá, tí ó sì fi rúbọ nígbà náà. Ṣùgbọ́n ẹsẹ náà sọ fún wa pé Olókun ṣẹ́gun pẹ̀lú ẹbọ rẹ̀ ìgbẹ̀hìn. Nítorí náà a lè sọ wí pé ẹbọ ìṣẹ́gun ni Olókun rú.

Ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ń ṣe àlàyé pé ẹni tí ó bá sún mọ́ ọba náà ni ńkọ ọba ń ṣà lẹ́sẹ̀. Ẹni tí ó bá takété dáadáa, ọkọ̀ ọba kò lè tètè ṣà á lẹ́sẹ̀. Ó ṣọ bí ẹni pé Ifá ń ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn ọmọ tálákà nítorí pé kí wọn ó ṣọra láti máa rìn mọ́ àwọn ọba tàbí ọlá nítorí ìpalára tí ó lè tibọ̀ jáde.